12. Bẹẹ ni OLUWA bukun igbẹhin Jobu ju iṣaaju rẹ̀ lọ; o si ni ẹgbaa-meje agutan, ẹgbaa-mẹta rakunmi, ati ẹgbẹrun àjàgà ọda-malu, ati ẹgbẹrun abo kẹtẹkẹtẹ. (Job 1:10; 8:7; 1:3.)
13. O si ni ọmọkunrin meje ati ọmọbinrin mẹta. (Job 1:2.)
14. O si sọ orukọ akọbi ni Jemima; ati orukọ ekeji ni Kẹsia; ati orukọ ẹkẹta ni Keren-happuki.
15. Ati ni gbogbo ilẹ naa, a ko ri obinrin ti o ni ẹwà bi ọmọbinrin Jobu; baba wọn si pin ilẹ fun wọn ninu awọn arakunrin wọn.
16. Lẹhin eyi Jobu wà ni ayé ni ogoje ọdun, o si ri awọn ọmọ rẹ̀ ọkunrin ati awọn ọmọ-ọmọ rẹ̀ ọkunrin, ani iran mẹrin. (Job 5:26; Owe 3:16.)
17. Bẹẹ ni Jobu kú, o gbó, o si kún fun ọjọ́. (Gen 25:8.)

19

# IWE PSALMU

## IWE KINNI.

### ORIN 1.

**Ayọ̀ ẹni-iwabi-Ọlọrun.**

IBUKUN ni fun ọkunrin naa ti ko rin ni imọ̀ awọn eniyan buburu, ti ko duro ni ọ̀nà awọn ẹlẹ́ṣẹ̀, ati ti ko si jókòó ni ibùjokòó awọn ẹlẹgàn. (Owe 4:14; Job 21:16; Psm 17:4; 26:5; Jer 15:17.)

2. Ṣugbọn didun-inu rẹ̀ wa ninu ofin Oluwa; ati ninu ofin rẹ̀ ni o nṣe àṣàrò lọsan ati loru. (Psm 119:35; Jos 1:8; Psm 119:1.)

3. Yoo si dabi igi ti a gbin si etí ipa odo, ti nso èso rẹ̀ jade ni akoko rẹ̀; ewé rẹ̀ ki yoo si rẹ̀; ati ohunkohun ti o ṣe ni yoo maa ṣe dédé. (Jer 17:8; Esk 47:12; Gen 39:3; Psm 128:2.)

**Òsì ẹni-aiwabi-Ọlọrun.**

4. Awọn eniyan buburu ko ri bẹẹ: ṣugbọn wọn dabi iyangbo ti afẹfẹ nfẹ lọ. (Job 21:18; Isa 17:13.)

5. Nitori naa awọn eniyan buburu ki yoo dide duro ni idajọ, bẹẹ ni awọn ẹlẹṣẹ ki yoo le duro ni àwùjọ awọn olododo. (Psm 5:5; 9:7, 8:16; 111:1; 149:1.)

6. Nitori Oluwa mọ ọ̀nà awọn olododo: ṣugbọn ọ̀nà awọn eniyan buburu ni yoo ṣègbé. (Psm 37:18; 2 Tim 2:19; Psm 9:3–6.)

### ORIN 2.

**Kíkọ Messiah silẹ̀.**

EṢE ti awọn orilẹ-ede fi ndi rikiṣi, ati tí awọn eniyan ngbiro ohun asan? (A.A. 4:25; Psm 21:11.)

2. Awọn ọba ayé kẹ́sẹ̀ jọ, ati awọn ijoye ngbìmọ̀ pọ̀ si Oluwa ati si Ẹni-àmìòróró rẹ̀ pe. (Psm 48:4–6; 74:18,23; Jhn 1:41.)

3. "Ẹ jẹ ki a fa idè wọn ja, ki a si mu okùn wọn kuro ni ọdọ wa." (Jer 5:5.)

**Oluwa yoo fi wọn ṣẹlẹ́yà.**

4. Ẹni ti o jókòó ni ọrun yoo rẹrin; Oluwa yoo yọ ṣùti si wọn. (Psm 59:8; 37:13; Owe 1:26.)

5. Nigba naa ni yoo sọrọ si wọn ni ibinu rẹ̀, yoo si yọ wọn lẹnu ninu ibanujẹ rẹ̀ kikan. (Psm 21:8,9; 78:49,50.)

6. Ṣugbọn mo ti fi Ọba mi jẹ lori Sioni, òkè mímọ́ mí. (Psm 3:4.)

**Messiah yoo yọ ayọ̀ Iṣẹgun.**

7. Emi o si rohin ipinnu Oluwa: O ti wi fun mi pe, "Iwọ ni Ọmọ mi, loni ni mo bi ọ. (A.A. 13:33; Heb 1:5.)

8. Beere lọwọ mi, emi o sì fi awọn orilẹ̀-èdè fun ọ ni ogún rẹ, ati iha opin ilẹ ni ilẹ-ini rẹ. (Psm 22:27.)

9. Ọpa irin ni iwọ o fi fọ wọn; iwọ o si run wọn wómú-wómú, bi ohun èlò amọ̀." (Psm 89:23; Ifh 2:27; 12:5.)

**Imoran ti Oluwa gba awọn Ọba.**

10. Njẹ nitori naa ki ẹyin o gbọ́n, ẹyin ọba: ki a si kọ yin, ẹyin onidajọ ayé.

11. Ẹ fi ìbẹ̀rù sin Oluwa, ẹ si maa yọ̀ pẹlu ìwárìrì. (Heb 12:28; Psm 119: 119,120.)

12. Fi ẹnu ko Ọmọ naa lẹnu, ki ó maṣe binu, ẹyin a si ṣègbé ni ọ̀nà naa, bi inu rẹ̀ ba ru diẹ kiun. Ibukun ni fun gbogbo awọn ti o gbẹkẹ wọn le e. (Jhn 5:23; Ifh 6:16; Psm 34:8; Rom 9:33.)

## ORIN 3.

**Dafidi fi ẹ̀sùn sùn.**

OLUWA, awọn ti nyọ mi lẹnu ti pọ̀ to yìí! ọpọlọpọ ni awọn ti o dide si mi. (2 Sam 15:12.)

2. Ọpọlọpọ ni awọn ti o nwi ni ti ọkàn mi pe, Iranlọwọ kò sí fun un nipa ti Ọlọrun. (Psm 71:11.)

**Ọlọrun ni igbẹkẹle rẹ̀.**

3. Ṣugbọn iwọ, Oluwa, ni asà fun mi; ogo mi; ati olùgbé ori mi sókè. (Psm 28:7; 27:6.)

4. Emi fi ohun mi kigbe si Oluwa, o si gbohùn mi lati òkè mímọ́ rẹ̀ wá. (Psm 34:4; 99:9.)

**Ọlọrun ni ààbò rẹ̀.**

5. Emi dùbúlẹ̀, mo sì sùn; mo si ji; nitori ti Oluwa tì mí lẹ́hìn. (Lef 26:6; Psm 139:18.)

6. Emi ki yoo bẹ̀rù ọpọlọpọ eniyan, ti wọn rọ̀gbà yi mi ká. (Psm 27:3.)

**Adura ati inudidun rẹ̀.**

7. Dide Oluwa; gba mi, Ọlọrun mi: nitori iwọ ni o lu gbogbo awọn ọ̀tá mi ni egungun ẹ̀rẹ̀kẹ́; iwọ si ka ehín awọn eniyan buburu. (Psm 7:6; 6:4; Job 16:10; Psm 58:6.)

8. Ti Oluwa ni igbala: ibukun rẹ̀ si nbẹ lara awọn eniyan rẹ̀. (Isa 43:11; Jer 3:23; Num 6:23–27.)

## ORIN 4.

**Ironu Dafidi ni òru; Adura fun iranlọwọ.**

GBOHUN mi nigba ti mo ba npe, Ọlọrun ododo mi: iwọ ni o da mi ni idè ninu ipọnju; ṣe ojurere fun mi, ki o si gbọ́ adura mi. (Psm 27:7; 18:6; 24:5; 25:16; 17:6.)

**O ba awọn ọta rẹ̀ wi.**

2. Ẹyin ọmọ eniyan, ẹ o ti sọ ogo mi di ìtìjú pẹ to? Ẹyin o ti fẹ́ asán pẹ to, ti ẹ o si maa wá èké lati ṣe? (Psm 31:6,18.)

3. Ṣugbọn ki ẹ mọ pe Oluwa ya ẹni ayanfẹ sọ́tọ̀ fun ara rẹ̀: Oluwa yoo gbọ́ nigba ti mo ba ké pe e. (Psm 31:23; 6:8,9.)

**O gba awọn ọ̀tá rẹ̀ niyànjú.**

4. Ẹ binu, ẹ ma sì ṣe ṣẹ; ẹ ba ọkàn yin sọ̀rọ̀ lori àkéte yin, ki ẹ si duro jẹ́ẹ. (Psm 33:8; Ef 4:26; Psm 77:6.)

5. Ẹ rú ẹbọ ọ̀dodo, ki ẹ si gbẹkẹ̀ yin le Oluwa. (Deut 33:19; Psm 50:14; 37:3.)

**Igbẹkẹle rẹ̀ ninu Ọlọrun.**

6. Ẹni pupọ ni o nwi pe, "Tani yoo ṣe rere fun wa? Oluwa, iwọ gbe imọlẹ oju rẹ soke si wa lara!" (Num 6:26.)

7. Iwọ ti fi ayọ̀ si mi ni inu, ju igba naa lọ tí ọkà wọn ati ọti-waini wọn di pupọ. (A.A. 14:17; Isa 9:3.)

8. Emi o dùbúlẹ̀ pẹlu ni alaafia, emi o si sùn; nitori iwọ, Oluwa, nikanṣoṣo ni o nmu mi jókòó láìléwu. (Psm 3:5; Lef 25:18.)

## ORIN 5.

**Adura owurọ, Oluwa ngbọ adura.**

FI etí si ọ̀rọ̀ mi, Oluwa, kiyesi àròyé mi. (Psm 54:2; 19:14.)

2. Fi etí si ohun ẹkún mi, Ọba mi, ati Ọlọrun mi: nitori ọ̀dọ rẹ lemi o maa gbadura si. (Psm 3:4; 84:3.)

3. Ohùn mi ni iwọ o gbọ ni owurọ, Oluwa, ni owurọ lemi o gba adura mi si ọ, emi o si maa wòkè. (Psm 88:13; Hab 2:1.)

**Inu Ọlọrun kò dun si iwa-buburu.**

4. Nitori ti iwọ kì í ṣe Ọlọrun ti nṣe inu-didun si iwa-buburu: bẹẹ ni ibi kò le bá ọ gbé. (Psm 11:5; 92:15.)

5. Awọn agberaga ki yoo le duro

niwaju rẹ: iwọ korira gbogbo awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ̀. (Psm 73:3; 1:5; 11:5.)
6. Iwọ o pa awọn ti nṣe ẹ̀ké run; Oluwa yoo korira awọn ẹni-ẹ̀jẹ̀, ati ẹni-ẹ̀tàn. (Ifh 21:8; Psm 55:23.)

**Ọlọrun maa nbukun awọn olododo.**

7. Ṣugbọn bi o ṣe temi, emi o wa sinu ile rẹ ni ọpọlọpọ aanu rẹ: ninu ẹ̀rù rẹ ni emi o tẹriba si iha tẹmpili mímọ́ rẹ. (Psm 69:13; 28:2.)
8. Tọ́ mi, Oluwa, ninu ododo rẹ, nitori awọn ọta mi: mu ọ̀nà rẹ tọ́ tàrà niwaju mi. (Psm 27:11; 31:1.)
9. Nitori ti otitọ kan kò si ni ẹnu ẹnikẹni wọn; ọkàn wọn kun fun ìkà iboji ti o ṣi silẹ ni ọ̀fun wọn; ahọ́n wọn ni wọn fi npọnni. (Deut 32:20; Luk 11:44; Rom 3:13; Psm 12:2.)
10. Iwọ da wọn lẹbi, Ọlọrun; ki wọn o ti ipa ìmọ̀ ara wọn ṣubú; ja wọn kuro nitori ọpọlọpọ irekọja wọn; nitori ti wọn ti ṣọ̀tẹ̀ si ọ. (Psm 9:16; E.Jer. 1:5; Psm 107:10,11.)
11. Nigba naa ni gbogbo awọn ti ngbẹkẹle ọ yoo yọ; lae wọn o maa hó fún ayọ̀, nitori ti iwọ dábò bò wọn: ati awọn ti o fẹ orukọ rẹ pẹlu yoo maa yọ ninu rẹ. (Psm 2:12; Isa 65:13; Sek 9:15; Psm 69:36.)
12. Nitori iwọ, Oluwa, ni yoo bukun fun olododo; ọju-rere ni iwọ o fi yi i ka bi asà. (Psm 112:2; 32:7,10.)

## ORIN 6.

**Adura fun aanu ni àkókò ibanujẹ.**

OLUWA, máṣe ba mi wi ni ibinu rẹ, ki iwọ ma ṣe na mi ni gbigbona ibanujẹ rẹ. (Psm 38:1; 2:5.)
2. Oluwa, ṣaanu fun mi; nitori ailera mi: Oluwa, mu mi lara dá; nitori ti ara kan egungun mi. (Psm 51:1; 102: 4,11; 41:4; 22:14.)
3. Ara kan ọkàn mi gógó pẹlu: ṣugbọn iwọ, Oluwa, yoo ti pẹ́ tó! (Jhn 12:27; Psm 90:13.)
4. Pada, Oluwa, gba ọkan mi: gbà mi là nitori aanu rẹ. (Psm 17:13.)
5. Nitori ti kò si iranti rẹ ninu òkú: ninu isà-òkú tani yoo dupẹ fun ọ? (Psm 30:9; Isa 38:18.)
6. Agara ikerora mi dá mi: ni òru gbogbo ni mo nmu àkéte mi fò loju omi; emi fi omije mi rin ibùsùn mi. (Psm 69:3; 22:1; 42:3.)
7. Oju mi bajẹ tan nitori ibanujẹ; o di ogbó tan nitori gbogbo awọn ọta mi. (Psm 31:9.)

**Idàniloju idahun adura.**

8. Ẹ lọ kuro lọ́dọ̀ mi, gbogbo ẹyin onísẹ́ ẹ̀ṣẹ̀; nitori ti Oluwa gbọ́ ohun ẹkún mi. (Psm 119:115; Luk 13:27; Psm 5:5; 28:6.)
9. Oluwa gbọ ẹ̀bẹ̀ mi; Oluwa yoo gba adura mi. (Psm 116:1; 66:19,20.)
10. Ojú yoo ti gbogbo awọn ọta mi, ara yoo si kan wọn gógó; wọn o pada, ojú yoo ti wọn lojiji. (Psm 71:24; 40:14; 73:19.)

## ORIN 7.

**Dafidi yipada si Ọlọrun.**

OLUWA, Ọlọrun mi, iwọ ni mo gbẹkẹ mi le: gba mi lọ́wọ́ gbogbo awọn ti nṣe inunibini si mi, ki o si yọ mi kuro. (Psm 11:1; 31:15.)
2. Ki o ma baa fa ọkàn mi ya bi kinniun, a ya a pẹ́rẹpẹ̀rẹ, nigba ti kò si oluranlọwọ. (Psm 17:12; 50:22.)

**Dafidi fi iwa rere rẹ hàn.**

3. Oluwa, Ọlọrun mi, bi mo ba ṣe eyi, bi ẹ̀ṣẹ̀ ba nbẹ lọwọ mi. (2 Sam 16:7; 1 Sam 24:11.)
4. Bi mo ba fi ibi san an fun ẹni ti tèmi tirẹ̀ wa ni alaafia. (Nitootọ ẹni ti nṣe ọta mi ni ainidi, emi tilẹ gba a la:) (1 Sam 24:7.)
5. Jẹ ki ọ̀tá o ṣe inunibini si ọkàn mi, ki o si mu un, ki o tẹ ẹmi mi mọ́lẹ̀, si fi ọkàn mi lé inu ekuru.

**Dafidi kigbe fun idajọ.**

6. Dide, Oluwa, ni ibinu rẹ! gbe ara rẹ soke nitori irunu awọn ọ̀tá mi: ji iwọ Ọlọrun mi si idajọ ti iwọ ti pa láṣẹ. (Psm 3:7; 94:2; 44:23.)
7. Jẹ ki ijọ awọn eniyan yi ọ ká kiri;

nję nitori wọn iwọ pada si òkè. (Psm 68:18.)

8. Oluwa yoo ṣe idajọ awọn eniyan: Oluwa ṣe idajọ mi, gẹgẹ bi ododo mi, ati gẹgẹ bi iwatitọ inu mi. (Psm 96:13; 18:20; 35:24.)

9. Jẹ ki iwa-buburu awọn eniyan buburu de opin: ṣugbọn mu olotitọ duro: nitori Ọlọrun olododo ni o ndán àyà ati inu wò. (Psm 34:21; Isa 54:14; 1 Kro 28:9; Jer 11:20; Ifh 2:23.)

**Òpin awọn eniyan buburu.**

10. Ààbò mi nbẹ lọdọ Ọlọrun ti o nṣe igbala olotitọ àyà. (Psm 18:2; 125:4.)

11. Ọlọrun ni onidajọ ododo, Ọlọrun si nbinu si eniyan buburu lojojumọ. (Psm 50:6; Isa 34:2.)

12. Bi oun ko ba yipada, yoo si pọ́n idà rẹ̀ mu: o ti fa ọrun rẹ̀ le ná, o ti mura rẹ̀ silẹ. (Esk 3:19; 33:9; Deut 32:41; Psm 21:12.)

13. O si ti pèsè elo ikú silẹ fun un, o ti ṣe awọn ọfa rẹ̀ ni oníná. (Psm 64:7.)

14. Kiyesi i, ẹni-ibi nrọbi ẹ̀ṣẹ̀, o si lóyún ìwà-ìkà, o si bi èké jáde. (Isa 59:4; Jak 1:15.)

15. O ti wá ọ̀fìn, o gbẹ́ ẹ́, o si ṣubu sinu ihò ti oun naa wà. (Job 4:8; Psm 9:15; Onws 10:8.)

16. Ìwà-ìkà rẹ̀ yoo si pada si orí ara rẹ̀, ati ìwà-agbára rẹ̀ yoo si sọ̀kalẹ̀ bọ́ si àtàrí ara rẹ̀. (Psm 140:9; Est 9:25.)

**Ìyìn fún Ọlọrun ododo.**

17. Emi o yin Oluwa gẹgẹ bi ododo rẹ̀: emi o si kọrin ìyìn sí orukọ Oluwa Ọga-ogo julọ. (Psm 71:15,16; 9:2.)

## ORIN 8.

**Ọlọrun Ẹlẹda ti o ga jù lọ.**

JEHOFAH, Oluwa wa, orukọ rẹ ti níyìn to ni gbogbo ayé! iwọ ti o gbe ògo rẹ ka orí awọn ọ̀run. (Psm 66:2; 148:13; 57:5,11; 113:4.)

2. Lati ẹnu awọn ọmọ-ọwọ́ ati ọmọ-ọmú ni iwọ ti ṣe ìlànà agbara, nitori awọn ọta rẹ, nitori ki iwọ le mu ọta olugbẹsan dakẹjẹ. (Matt 21:16; Psm 44:16.)

3. Nigba ti mo ro ọ̀run rẹ, iṣẹ́ ìka rẹ, òṣùpá ati ìràwọ̀, ti iwọ ti ṣe ilana silẹ. (Psm 89:11; 102:5; 136:9.)

4. Kinni eniyan, ti iwọ fi nṣe iranti rẹ? Ati ọmọ eniyan, ti iwọ fi nbẹ ẹ wo. (Job 7:17; Psm 144:3; Heb 2:6.)

**Eniyan jẹ aṣoju Ọlọrun to ga julọ.**

5. Iwọ saa da a ni onirẹlẹ diẹ ju Ọlọrun lọ, iwọ si ti fi ogo ati ọlá de e ni adé. (Psm 103:4; 21:5; Heb 2:9.)

6. Iwọ mu un jọba iṣẹ́ ọwọ́ rẹ; iwọ si ti fi ohun gbogbo sábẹ́ ẹsẹ̀ rẹ̀. (Gen 1:26; Heb 2:8.)

7. Awọn àgùtàn ati awọn malu pẹlu awọn ẹranko ìgbẹ́

8. Awọn ẹyẹ oju ọrun ati ẹja inu òkun ti o nkọja lọ nipa ọ̀nà ọ̀kun.

9. Jehofah, Oluwa wa orukọ rẹ ti ni ìyìn tó ni gbogbo ayé (ẹsẹ 1.)

## ORIN 9.

**Dafidi kọ orin ìyìn ati ọpẹ́ si Ọlọrun.**

EMI o fi gbogbo àyà mi yin Oluwa; emi o fi gbogbo iṣẹ́ iyanu rẹ hàn. (Psm 86:12; 26:7.)

2. Emi o yọ̀, emi o si ṣe inu-didun ninu rẹ̀, emi o si kọrin ìyìn si orukọ rẹ, iwọ Ọga-ogo julọ. (Psm 5:11; 83:18.)

3. Nigba ti awọn ọta mi ba pẹhinda, wọn o ṣubu, wọn o si ṣègbé ni iwaju rẹ. (Psm 56:9; 27:2.)

4. Nitori iwọ ni o ti mu idajọ mi ati ìdí ọ̀ràn mi duro; iwọ ni o jókòó lori ìtẹ́, ti o nṣe idajọ ododo. (Psm 140:12; 47:8; 67:4; 1 Pet 2:23.)

5. Iwọ ba awọn orilẹ-ede wi, iwọ pa awọn eniyan buburu run, iwọ pa orukọ wọn rẹ lae ati laelae. (Deut 9:14.)

6. Niti ọta, iparun wọn pari tan laelae: iwọ ni o si ti run awọn ilu wọn; iranti wọn si ti ṣègbé pẹlu wọn. (Psm 40:15; 34:16.)

**Igbagbọ ninu ododo Ọlọrun.**

7. Ṣugbọn Oluwa yoo wà titi laelae: o ti tẹ́ itẹ rẹ̀ silẹ fun idajọ. (Psm 29:10; 89:14.)

8. Oun o si ṣe idajọ ayé ni ododo, yoo ṣe idajọ fun awọn eniyan ni otitọ ìwà. (Psm 96:13.)

9. Oluwa ni yoo ṣe ààbò awọn ẹni-inilara, ààbò ni igba ìpọ́njú. (Psm 18:2; 32:7; 37:39.)

10. Awọn ti o si mọ orukọ rẹ yoo gbẹkẹ le ọ: nitori iwọ, Oluwa, kò kọ awọn ti nṣe afẹri rẹ silẹ. (Psm 91:14; 37:28.)

11. Ẹ kọrin iyin si Oluwa, ti o jókòó ni Sioni: ẹ fi iṣẹ́ rẹ hàn ninu awọn eniyan. (Psm 76:2; 105:1.)

12. Nigba ti o wadi ẹjọ́-ẹ̀jẹ̀, o ranti wọn: oun kò sì gbagbe ẹkún awọn olupọnju. (Gen 9:5; ẹsẹ 18.)

**Adura fun Iranwọ.**

13. Ṣaanu fun mi, Oluwa; ro iṣẹ́ ti emi nṣẹ́ lọwọ awọn ti o korira mi, iwọ ti o gbe ori mi soke kuro ni ẹnu-ọ̀nà ikú. (Psm 30:10; 25:18; 38:19; 30:3.)

14. Ki emi baa lè maa fi gbogbo ìyìn rẹ hàn ni ẹnu-ọna ọmọbinrin Sioni, emi o maa yọ̀ ni ìgbàlà rẹ. (Psm 106:2; 87:2; 13:5.)

**Ijẹri si awọn idajọ Ọlọrun.**

15. Awọn orilẹ-èdè jin sinu ọ̀fin ti wọn wa: ninu àwọ̀n ti wọn dẹ silẹ ni ẹsẹ̀ ara wọn kọ́. (Psm 7:15; 35:8.)

16. A mọ Oluwa, nipa idajọ ti o nṣe: nipa iṣẹ́ ọwọ́ eniyan buburu ni a fi ndẹkùn mu un. (Isa 64:2; ẹsẹ 4.)

**Idaniloju ati Adura fun idajọ.**

17. Awọn eniyan buburu ni a o dà si ìsà-ọ̀kú, ati gbogbo orilẹ-ede ti o gbagbe Ọlọrun. (Psm 49:14; 50:22; Job 8:13.)

18. Nitori pe a ki yoo gbagbe awọn alaini laelae: ìrètí awọn talaka ki yoo ṣegbe laelae. (ẹsẹ 12; Psm 74:19.)

19. Oluwa, dide; máṣe jẹ ki eniyan o bori: jẹ ki a ṣe idajọ awọn orilẹ-ede niwaju rẹ. (Psm 3:7; 2 Kro 14:11; Psm 110:6.)

20. Dẹ́rù ba wọn, Oluwa: ki awọn orilẹ-èdè mọ̀ ara wọn pé, eniyan ni wọn. (Psm 83:15; Isa 31:3.)

## ORIN 10.

**Ìwà ibi awọn eniyan buburu.**

EESE ti iwọ fi duro ni òkèrè réré, Oluwa; eeṣe ti iwọ fi fi ara pamọ́ ni ìgbà ipọnju?

2. Ninu igberaga ni eniyan buburu nṣe inunibini si awọn talaka: ninu àrekérekè ti wọn rò ni ki a ti mu wọn. (Psm 109:16; 7:15; 9:16.)

3. Nitori eniyan buburu nṣogo ìfẹ́ ọkàn rẹ̀, o si nsúre fun olójúkòkòrò, o si nkẹgan Oluwa. (Psm 94:4; Job 1:5,11; ẹsẹ 13.)

4. Eniyan buburu, nipa igberaga oju rẹ̀, ko fẹ ṣe afẹri Ọlọrun: gbogbo ironu rẹ ni wi pe, "Ọlọrun ko si." (ẹsẹ 13; Psm 14:1.)

5. Ọ̀nà rẹ̀ nlọ, déédé siwaju nigba gbogbo; idajọ rẹ̀ jinna réré kuro ni ojú rẹ̀, fun gbogbo awọn ọ̀tá rẹ̀, ni oun nṣẹ̀fẹ̀ sí.

6. O ti ro o ni ọkàn rẹ̀ pe, "A kì yoo ṣi mi ni ipò: lati irandiran emi ki yoo si ninu ipọnju." (Psm 30:6; 49:11.)

7. Ẹnu rẹ̀ kún fun ègún, ati fun ẹ̀tàn, ati fun ìtànjẹ: ìwà-ìkà ati ìwà-asán nbẹ labẹ ahọ́n rẹ̀. (Rom 3:14; Psm 59:12; 73:8; 140:3.)

8. O jókòó ni bùba ninu awọn iletò: ni ibi ìkọ̀kọ̀ ni o npa awọn alaiṣẹ̀: oju rẹ̀ nṣọ́ awọn talaka níkọ̀kọ̀. (Owe 1:11; Psm 94:6.)

9. Ó ba ni ibi ìkọ̀kọ̀ bi kinniun ninu panti: o ba lati mu tálákà: a si mu tálákà, nigba ti o ba fa a sinu àwọ̀n rẹ̀. (Psm 17:12; 59:3; ẹsẹ 2; Psm 140:5.)

10. O ba, o rẹ ara rẹ̀ silẹ̀, ki talaka baa le bọ́ si ọwọ́ agbara rẹ̀.

11. O ti wi ni ọkàn rẹ̀ pe, "Ọlọrun ti gbagbe: o pa ojú rẹ̀ mó; oun ki yoo ri i laelae." (ẹsẹ 4; Job 22:13; Psm 73:11.)

**Adura fun Iranlọwọ ati Igbẹkẹle fún idahun.**

12. Dide, Oluwa; Ọlọrun, gbe ọwọ́ rẹ soke: máṣe gbagbe olupọnju. (Mika 5:9; Psm 9:12.)

13. Eeṣe ti eniyan buburu fi ngan Ọlọrun? O wi ni ọkàn rẹ̀ pé, "Iwọ ki yoo bèèrè". (ẹsẹ 3.)

14. Iwọ ti ri i; nitori iwọ nwo ìwà-ìkà ati ìwọ̀sí, lati fi ọ̀ràn naa le ọwọ́ rẹ; tálákà fi ara rẹ̀ le ọ lọwọ; ìwọ ni oluranlọwọ alainibaba. (Job 11:11; Jer 51:56; Psm 37:5; 68:5; Hos 14:3.)

15. Ṣẹ́ apá eniyan buburu, ati ti ọkunrin ibi: iwọ wá iwa-buburu rẹ̀ rí, titi iwọ kì yoo fi ri i mọ́. (Psm 37:17; 9:12.)

16. Oluwa ni ọba lae, ati laelae: awọn keferi run kuro ni ilẹ̀ rẹ̀. (Psm 29:10; Deut 8:20.)

17. Oluwa, iwọ ti gbọ́ ifẹ onirẹlẹ: iwọ o mu ọkàn wọn yè, iwọ o dẹ etí rẹ si i. (Psm 145:19; 1 Kro 29:18; Psm 34:15.)

18. Lati ṣe idajọ alaini-baba ati ẹni-inilara, ki ọkunrin ayé maṣe daya-fo ni mọ́. (Psm 82:3; 9:9; Isa 29:20.)

## ORIN 11.

**Ninu Oluwa ni ààbò mi wa.**

OLUWA ni mo gbẹkẹ mi le: ẹ o ha ti ṣe wi fun ọkàn mi pe, "Sá bi ẹyẹ lọ si òkè yin? (Psm 56:11.)

2. Sa kiyesi i, awọn eniyan buburu ti fa ọrun wọn le, wọn ti fi ọfa sii ni oju ọ̀ṣán, ki wọn le ta a ni òkùnkùn si ọlọ́kàn diduro. (Psm 7:12; 64:3,4.)

3. Bi ipilẹ ba bajẹ, kinni olododo yoo ṣe (Psm 82:5.)

**Titẹnumọ Igbagbọ ninu Ọlọrun.**

4. Oluwa nbẹ ninu tẹmpili mimọ rẹ̀, ìtẹ́ Oluwa nbẹ ni ọ̀run: oju rẹ nwo awọn ọmọ eniyan, ipenpeju rẹ̀ ndán awọn ọmọ eniyan wò. (Psm 18:6; 103:19; 33:13; 34:15,16.)

5. Oluwa ndan olododo wò: ṣugbọn eniyan buburu ati ẹni ti nfẹ ìwà-agbàra, ọkàn rẹ̀ korira. (Gen 22:1; Jak 1:12; Psm 5:5.)

6. Lori eniyan buburu ni yoo rọ̀jò, ẹyin gbigbona ati imí-ọjọ́ ati ìjì gbigbona sí: eyi ni ìpín ago wọn. (Esk 38:22; Jer 4:11,12.)

7. Nitori olododo ni Oluwa, o fẹ ododo; awọn ẹni ti o duro-ṣinṣin yoo rí ojú rẹ̀. (Psm 7:9,11; 33:5; 17:15.)

## ORIN 12.

**Adura fun iranlọwọ laarin awọn alaiwabi-Ọlọrun.**

GBA-NI Oluwa! nitori awọn ẹni iwabi-Ọlọrun kò si mọ; nitori awọn olootọ ti parẹ́ kuro ninu awọn ọmọ eniyan. (Isa 57:1.)

2. Olukuluku wọn nba ẹnikeji rẹ̀ sọ asán; ètè ipọnni ati ọkàn meji ni wọn fi nsọ. (Psm 41:6; 55:21; 1 Kro 12:33.)

3. Oluwa yoo ge gbogbo ètè ipọnni kuro, ati ahọ́n ti nsọ̀rọ̀ ohun nla. (Psm 73:8,9.)

4. Ti o wi pe, "Ahọ́n wa ni àwa o fi ṣẹgun; ètè wa ni ti wa: tani nṣe oluwa wa?"

**Idaniloju Igbala Ọlọrun.**

5. "Nitori ìnira awọn talaka, nitori ìmí-ẹ̀dùn awọn alaini, Oluwa wi pe, 'Nigbayìí ni emi o dide; emi o si mun un lọ si ibi ailewu kuro lọwọ ẹni ti nhalẹ̀ mọ ọ.'" (Psm 10:18; 3:7; 34:6.)

6. Ọrọ̀ Oluwa, ọ̀rọ̀ pípé ni, bi fàdákà ti a yọ́ ninu ìleru erùpẹ̀, ti a dà ni ìgbà meje. (Psm 18:30; Owe 30:5.)

7. Iwọ o pa wọn mọ́, Oluwa, iwọ o pa olukuluku wọn mọ́ kuro lọwọ iran yìí laelae. (Psm 37:28.)

8. Awọn eniyan buburu nrin ni ìhà gbogbo, nigba ti a ba gbé awọn eniyan-keniyan léke. (Psm 55:10, 11.)

## ORIN 13.

**A ha gbagbe Dafidi bi?**

IWỌ o ti gbagbe mi pẹ tó, Oluwa, laelae? Iwọ o ti pa ojú rẹ mọ pẹ to kuro lara mi? (Job 13:24; Psm 44:24; 88:14.)

2. Emi o ti maa gbìmọ̀ ni ọkàn mi pẹ tó? Ti emi o maa ni ibanujẹ ni ọkan mi lojojumọ? Ọ̀tá mi yoo ti gberaga sori mi pẹ́ tó? (Psm 42:4,9; 94:3.)

**Adura Dafidi fun Iranwọ.**

3. Rò ó, ki o si gbohun mi, Oluwa Ọlọrun mi: mu oju mi mọ́lẹ̀, ki emi má baa sun orun ikú. (Psm 5:1; Esra 9:8; Jer 51:39.)

4. Ki ọta mi má baa wi pe, emi ti ṣẹgun rẹ̀; awọn ti nyọ mi lẹ́nu a si maa yọ̀, nigba ti a ba ṣí mi nípò. (Jer 20:10; Psm 25:2.)

**Dafidi ni idaniloju igbàlà.**

5. Ṣugbọn emi o gbẹkẹle aanu rẹ; ọkàn mi yoo yọ̀ ní igbala rẹ. (Psm 52:8; 9:14.)

6. Emi o maa kọrin si Oluwa, nitori ti o ṣeun fun mi lọpọlọpọ. (Psm 59:16; 116:7.)

ORIN 14.

**Ẹ̀kọ́ ati Iṣẹ awọn eniyan buburu.**

ASIWERE (omugọ) wi ni ọkan rẹ̀ pe, "Ọlọrun ko si." Wọn bajẹ, wọn si nṣe iṣẹ irira, ko si ẹni ti nṣe rere. (Psm 10:4; 53:1–6; 73:8; Rom 3:10–12.)

2. Oluwa bojuwo lati ọrun sara awọn ọmọ eniyan, lati wò bi ẹnikan wà ti òye yé, ti o si nwá Ọlọrun. (Psm 33:13; 92:6; Esra 6:21.)

3. Gbogbo wọn ni o si jùmọ̀ ya si apakan, wọn si di eleeri patapata; kò si ẹni ti nṣe rere, kò si ẹnikan. (Psm 58:3; 2 Pet 2:7; Ifh 22:11; Psm 143:2.)

4. Gbogbo awọn ti nṣiṣẹ ẹ̀ṣẹ̀ ko ni ìmọ̀ bi? Awọn ẹni ti njẹ eniyan mi bi ẹni jẹ àkàrà ti wọn kò si ke pe Oluwa. (Psm 82:5; 27:2; 79:6; Isa 64:7.)

5. Nibẹ ni ẹ̀rù bà wọn gidigidi: nitori ti Ọlọrun nbẹ ninu ìran olododo: (Psm 73:15.)

6. Ẹyin dojuti ìmọ̀ràn awọn tálákà, ṣugbọn Oluwa ni ààbò rẹ̀. (Psm 9:9; 40:17.)

7. Igbala Israeli iba jẹ́ jade wá lati Sioni! Nigba ti Oluwa bá mu ìkólọ awọn eniyan rẹ̀ pada bọ̀, Jakọbu yoo yọ̀, inu Israẹli yoo si dun. (Psm 53:6; Job 42:10.)

ORIN 15.

**Idunnu awọn Alaiṣẹ.**

OLUWA, tani yoo maa ṣe àtìpó ninu agọ rẹ? Tani yoo maa gbe inu oke mimọ rẹ? (Psm 24:3–5; 27:5,6; 2:6.)

2. Ẹni ti o nrin deede, ti nṣiṣẹ ododo, ti o si nsọ otitọ lati inu rẹ̀, (Psm 24:4; 51:6; Ef 4:25.)

3. Ẹni ti kò fi ahọn rẹ̀ sọrọ ẹni lẹhin, ti kò si ṣe ibi si ẹnikeji rẹ̀, ti kò si gba ọ̀rọ̀ ẹ̀gàn si ẹnikeji rẹ̀. (Lef 19:16; Eks 23:1.)

4. Ni oju ẹni ti eniyan-keniyan di gígàn; ṣugbọn a maa bu ọlá fun awọn ti o bẹ̀rù Oluwa. Ẹni ti o bura si ibi ara rẹ̀, ti kò si yipada. (2 Tim 3:8; A.A. 28:10; Ondj 11:35.)

5. Ẹni ti kò fi owó rẹ, gba èlé, ti kò si gba owó ẹ̀bẹ̀ si aláìṣẹ̀. Ẹni ti o ba ṣe nkan wọnyìí ki yoó yẹsẹ̀ laelae. (Eks 22:25; 23:8; Deut 16:19; Psm 112:6.)

ORIN 16.

**Ijẹri igbagbọ.**

OLỌRUN, pa mi mọ́: nitori iwọ ni mo gbẹkẹ mi lé. (Psm 17:8; 7:1.)

2. Ọkàn mi, iwọ ti wi fun Oluwa pe, "Iwọ ni Oluwa mi: emi kò ni ire kan lẹhin rẹ." (Psm 73:25.)

3. Si awọn eniyan mímọ́ ti o wà ni ayé, ani si awọn ọlọ́lá, lara ẹni ti didun inu mi gbogbo gbé wà. (Deut 33:3; Psm 101:6.)

4. Ibanujẹ awọn ti nsare tọ ọlọrun miran lẹhin yoo pọ: ẹbọ ohun mímu ẹ̀jẹ̀ wọn ni emi ki yoo ta silẹ̀, bẹẹ ni emi ki yoo dá orukọ wọn lẹnu mi. (Psm 32:10; 106:37,38; Eks 23:13.)

**Asọtẹlẹ nipa ibi Agbelebu.**

5. Oluwa ni ìní mi ti mo yàn, ati ago mi: iwọ ni o mu ìpín mi duro (Psm 73:26; 23:5; 125:3.)

6. Okùn-tita bọ́ sọdọ mi ni ibi daradara: lootọ, emi ní ogún rere. (Psm 78:55; Jer 3:19.)

7. Emi o fi ibukun fun Oluwa, ẹni ti o ti nfun mi ni ìmọ̀; ọkàn mi pẹlu nkọ́ mi ni wakati òru. (Psm 73:24; 77:6.)

8. Emi ti gbe Oluwa ka iwájú mi nigba gbogbo; nitori ó wà lọwọ ọ̀tún mi, a ki yoo ṣí mi ni ipò. (Psm 54:3; 73:23; 62:2.)

**Idaniloju Ajinde.**

9. Nitori naa ni inu mi ṣe dun, ti ogo mi si nyọ̀; ara mi pẹlu yoo sinmi ni ireti. (Psm 4:7; 30:12; 4:8.)

10. Nitori iwọ ki yoo fi ọkàn mi silẹ̀ ni isà-okú; bẹẹ ni iwọ ki yoo jẹ́ ki Eni Mimọ rẹ ri ìdibàjẹ́. (A.A. 2:27; 13:35; Psm 49:9.)

11. Iwọ o fi ipa ọ̀nà ìyè hàn mi; ni iwaju rẹ ni ẹ̀kún ayọ̀ wà: lọwọ ọ̀tún rẹ ni didun-inu wa laelae. (Matt 7:14; Psm 17:15; 36:7,8.)

## ORIN 17.

**Dafidi bẹ̀bẹ̀ fún idalare.**

GBỌ ti otitọ, Oluwa, fiyesi igbe mi, fi etí si adura mi, ti kò ti ètè ẹ̀tàn jade. (Psm 9:4; 61:1; 55:1; Isa 29:13.)

2. Jẹ ki idajọ mi maa ti iwaju rẹ jáde wá: jẹ ki ojú rẹ maa wo ohun ti ó ṣe déédé. (1 Kro 29:17.)

3. Iwọ ti dan àyà mi wò; iwọ ti bẹ̀ ẹ́ wò ni òru; iwọ ti wadi mi, iwọ kò ri nkan; emi ti pinnu rẹ̀ pe, ẹnu mi ki yoo ṣẹ̀. (Psm 26:2; 66:10; Job 23:10; Jer 50:20; Psm 39:1.)

4. Niti iṣẹ́ eniyan, nipa ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ̀ emi ti pa ara mi mọ kuro ni ipa ìkà. (Owe 1:15.)

5. Fi ìṣísẹ̀ mi lé ilẹ̀ ni ipa-ọ̀nà rẹ, ki àtẹ́lẹsẹ̀ mi máṣe yẹ̀. (Psm 44:18; 18:36.)

**O gbadura fun idasi Ọlọrun.**

6. Emi ti nke pe ọ, nitori pe iwọ o gbohun mi, Ọlọrun: dẹ eti rẹ si mi, ki o si gbọ́ ọ̀rọ̀ mi. (Psm 86:7; 88:2.)

7. Fi iṣeun ifẹ iyanu rẹ hàn, iwọ ti o fi ọwọ́ ọ̀tún rẹ gba awọn ti o gbẹkẹle ọ là, lọwọ awọn ti o dide si wọn. (Psm 31:21; 20:6.)

8. Pa mí mọ́ bi ọmọ-ojú, pa mí mọ́ lábẹ́ òjìji ìyẹ́-apá rẹ. (Deut 32:10; Psm 36:7.)

9. Lọwọ awọn eniyan buburu ti nfòòró mi, lọwọ awọn ọ̀tá-oníkúpani, ti o yi mi ka. (Psm 31:20; 38:12; 108:3.)

**O ṣapejuwe awọn ọ̀tá rẹ̀.**

10. Wọn ti fi ọ̀rá sé àyà wọn, ẹnu wọn ni wọn fi nsọ̀rọ igberaga. (Psm 73:7; 1 Sam 2:3; Psm 31:18.)

11. Wọn ti yi wa ká nisinsinyìí ninu ìrìn wa; wọn ti gbe ojú wọn lé wíwọ́ wa silẹ. (Psm 88:17; 37:14.)

12. Bi kinniun ti nṣe iwọra si ohun ọdẹ rẹ̀, ati bi ọmọ kinniun ti o nba ni ibi ìkọ̀kọ̀. (Psm 7:2; 10:9.)

**Ó sọ̀rọ̀ igbẹkẹle rẹ̀ ninu Ọlọrun.**

13. Dide, Oluwa, ṣáaju rẹ̀, rẹ̀ ẹ́ sílẹ̀: gba ọkan mi lọ́wọ́ awọn eniyan buburu, pẹlu idà rẹ: (Psm 73:18; 22:20; 7:12.)

14. Lọ́wọ́ awọn eniyan nipa ọwọ́ rẹ, Oluwa, lọwọ awọn eniyan ayé, ti wọn ni ìpín wọn ni ayé yìí, ati ikùn ẹni ti iwọ fi ohun iṣura rẹ ìkọ̀kọ̀ kún: awọn ọmọ wọn pọ̀, wọn a si fi iyoku ìní wọn silẹ fun awọn ọmọ-ọwọ́ wọn. (Luk 16:8; Psm 73:3–7; Isa 2:7; Job 21:11.)

15. Bi o ṣe temi ni, emi o maa wo ojú rẹ ni ododo: àwòrán rẹ yoo tẹ́ mi lọrun nigba ti mo ba jí. (1 Jhn 3:2; Psm 4:6,7; 16:11.)

## ORIN 18.

**Orin ìdáǹdè kuro lọwọ ọ̀tá.**

EMI o fẹ ọ, Oluwa, agbara mi. (Psm 27:1.)

2. Oluwa ni apata mi, ati ilu-olodi mi, ati olugbala mi: Ọlọrun mi, agbara mi, emi o gbẹkẹle e; asà mi, ati ìwo igbala mi, ati ile-ìṣọ́ giga mi. (Psm 19:14; 91:2; 40:17; 11:1; 59:11; 75:10; 9:9.)

3. Emi o ke pe Oluwa, ti o yẹ lati maa yìn; bẹẹ ni a o si gbà mi lọwọ awọn ọ̀tá mi. (Psm 48:1; Num 10:9.)

**Dafidi jẹri si igbala rẹ̀.**

4. Ìrora ikú yi mi ka, ati iṣan-omi awọn eniyan buburu dẹruba mi. ( Psm 116:3; 124:3,4.)

5. Irora isà-okú yi mi ka: ikẹkun ikú di mi mu. ( Psm 116:3; Owe 14:27.)

6. Ninu ìṣẹ́ mi emi ke pe Oluwa, emi si sọkun pe Ọlọrun mi: o gbohun mi lati inu tempili rẹ̀ wá, ẹkún mi si wa si iwaju rẹ̀, ani si etí rẹ̀. ( Psm 86:7; 11:4; 34:15.)

7. Nigba naa ni ilẹ mì, o si wárìrì; ipilẹ òkè pẹlu ṣidi, ó sì mì, nitori ti o binu. ( Psm 68:7,8; 114:4,6.)

8. Eefin ti ihò imú rẹ̀ jade, ati iná lati ẹnu rẹ wa njonirun: ẹyín gbiná nipasẹ rẹ̀. (Deut 29:20; Hab 3:5.)

9. Ó tẹrí ọ̀run ba pẹlu, o si sọkalẹ wa: okunkun si nbẹ labẹ ẹsẹ̀ rẹ̀. (Psm 144:5; Eks 20:21.)

10. O si gun orí kerubu, o si fò: nitootọ, o nra lori iyẹ-apá afẹ́fẹ́. ( Psm 80:1; 104:3.)

11. O fi òkùnkùn ṣe ibi ìkọ̀kọ̀ rẹ̀: ani àgọ́ rẹ̀ yi i ka; omi dudu, ati awọsanma ojú-ọ̀run ṣiṣu dùdù. ( Psm 97:2.)

12. Nipa imọlẹ iwaju rẹ̀, awọsanma ṣíṣú dudu rẹ̀ kọja lọ, yìnyín ati ẹyín iná. (Psm 104:2; Isa 30:30; Psm 140:10.)

13. Oluwa sán ààrá pẹlu ni ọ̀run, Ọga-ogo si fọ ohun rẹ: yìnyín ati èyin iná! ( Psm 29:3; 104:7.)

14. Lootọ, o ran ọfà rẹ̀ jade, o si tu wọn ká: ati ọpọlọpọ mànàmáná ni o si fi ṣẹ́ wọn tuutu. ( Psm 7:13; 144:6; Eks 14:24; Ondj 4:15.)

15. Ni igba naa ni isàlẹ̀ omi odò hàn, a si ri ipilẹ ayé nipa ibawi rẹ, Oluwa, nipa fifun eemi ihò imú rẹ. ( Psm 106:9; 76:6; Eks 15:8.)

16. O ranṣẹ wa lati òkè, o mu mi, o fa mi jade lati inu omi nla. ( Psm 144:7.)

17. O gba mi lọwọ ọ̀tá mi alagbara, ati lọwọ awọn ti o korira mi; nitori wọn lagbara ju mi lọ. (ẹsẹ 48; Psm 35:10.)

18. Wọn dojukọ mi lọjọ ìpọnju mi, ṣugbọn Oluwa ni aláfẹ̀hìntì mi. ( Psm 59:16; Isa 10:20.)

19. O mu mi jade pẹlu sinu ibi nla; o gba mi nitori inu rẹ̀ dùn si mi. ( Psm 31:8; 118:5; 37:23.)

**O da iwa otitọ rẹ̀ lare.**

20. Oluwa san an fun mi gẹgẹ bi ododo mi; gẹgẹ bi mímọ́ ọwọ́ mi ni o san an fun mi. (Psm 7:8; 1 A.Ọba 8:32; Psm 24:4.)

21. Nitori mo ti nkiyesi ọ̀nà Oluwa, emi ko fi ìka yà kuro lọdọ Ọlọrun mi. ( Psm 119:33; 2 Kro 34:33; Psm 119:102.)

22. Nitori pe gbogbo idajọ rẹ̀ ni o wà niwaju mi, bẹẹ ni emi kò sì yẹ òfin rẹ̀ kuro lọdọ mi. ( Psm 119:30,83.)

23. Emi si duro ṣinṣin pẹlu rẹ̀, emi si paramọ́ kuro lara ẹ̀ṣẹ̀ mi.

24. Nitori naa ni Oluwa ṣe san an fun mi gẹgẹ bi ododo mi, gẹgẹ bi mímọ́ ọwọ mi loju rẹ̀. (1 Sam 26:23.)

25. Fun alaanu ni iwọ o fi ara rẹ hàn ni alaanu; fun ẹni ti o duroṣinṣin ni iwọ o fi ara rẹ hàn ni diduro-ṣinṣin. (Psm 62:12; Matt 5:7.)

26. Fun ọlọ́kàn-mímọ́ ni iwọ o fi ara rẹ hàn ni ọlọkan-mimọ; ati fun ọlọkan-wíwọ́ ni iwọ o fi ara rẹ hàn ni ònrorò. (Job 25:5; Owe 3:34.)

27. Nitori iwọ o gba awọn olupọnju; ṣugbọn iwọ o sọ ojú igberaga kalẹ̀. (Psm 72:12; Owe 6:17.)

28. Nitori iwọ ni yoo tan fitílà mi: Oluwa Ọlọrun mi yoo tan imọlẹ si òkùnkùn mi. (Job 18:6; Psm 27:1; Job 29:3.)

29. Nitori, pe pẹlu rẹ, emi sure la inu ogun lọ: ati pẹlu Ọlọrun mi emi fo odi kan. (2 Kor 12:9; Heb 11:34.)

30. Bi o ṣe ti Ọlọrun ni, ọ̀nà rẹ̀ pé: a ti ridi ọ̀rọ̀ Oluwa: oun ni apata fun gbogbo awọn ti o gbẹkẹle e. (Deut 32:4; Psm 12:6; 17:7.)

**Dafidi jẹ́wọ́ wi pe Ọlọrun ti gba oun.**

31. Nitori pe tani Ọlọrun, bikoṣe Oluwa? Tabi tani apata bikoṣe Ọlọrun

wa? (Deut 32:31,39; Psm 86:8–10; Isa 45:5.)

32. Ọlọrun ni o fi agbara di mi ni amure, o si mu ọ̀nà mi pe. (Isa 45:5; Heb 13:21; 1 Pet 5:10.)

33. O ṣe ẹsẹ̀ mi bi ẹsẹ̀ àgbọ̀nrín, o si gbé mi ka ibi giga mi. (Hab 3:19; Deut 32:13.)

34. O kọ́ ọwọ́ mi ni ogun jíjà, tobẹẹ ti apá mi fa ọrun idẹ. (Psm 144:1; Job 20:24.)

35. Iwọ ti fi asà igbala rẹ fun mi pẹlu: ọwọ́ ọtún rẹ si gbé mi duro, ati iwa-pẹlẹ rẹ sọ mi di nla. (Deut 33:29; Psm 119:117; 136:6.)

36. Iwọ sọ ìrìn ẹsẹ̀ mi di nla nisalẹ mi, ki kókó-ẹsẹ̀ mi máṣe yẹ̀. (Psm 31:8; 71:5.)

37. Emi ti le awọn ọta mi, emi si ba wọn: bẹẹ ni emi kò pada sẹ́hìn titi a fi run wọ́n. (Psm 44:5; 37:20.)

38. Emi ṣá wọn ni ọgbẹ́ ti wọn kò fi lè dide, wọn ṣubu labẹ ẹsẹ̀ mi. (Psm 110:6; 36:12; 47:3.)

39. Nitori ti iwọ fi agbara di mi ni àmùrè si ogun naa: iwọ ti mu awọn ti o dide si mi tẹriba labẹ ẹsẹ̀ mi. (ẹsẹ 32,47.)

40. Iwọ si yi ẹ̀hìn awọn ọ̀tá mi pada fun mi pẹlu; emi si pa awọn ti o korira mi run. (Psm 21:21; 94:23.)

41. Wọn kigbe, ṣugbọn kò si ẹni ti o gbà wọ́n; ani si Oluwa, ṣugbọn kò dá wọn lóhùn. (Psm 50:22; Owe 1:28.)

42. Nigba naa ni mo gún wọn kunna bi ekuru niwaju afẹ́fẹ́: mo ko wọn jade bi ẹrẹ̀ ni ìta. (Psm 83:13.)

**Dafidi mọ pe ọjọ́ ọ̀la yoo dara.**

43. Iwọ ti yọ mi kuro ninu ìjà awọn eniyan; iwọ fi mi jẹ olori awọn orilẹ-èdè: eniyan ti emi kò mọ̀, yoo si maa sìn mi. (Psm 35:1; Isa 52:15; 55:5.)

44. Bi wọn ti gburo mi, wọn o gbà mi gbọ́: awọn ọmọ àjèjì yoo fi ẹ̀tàn tẹ orí wọn ba fun mi. (Psm 66:3.)

45. Àyà yoo pá awọn alejo, wọn o si fi ibẹru jade ni ibi kọ̀lọ́fín wọn.

46. Oluwa nbẹ; olubukun si ni apata mi; ki a si gbé Ọlọrun ìgbàlà mi lékè. (Psm 42:2; 51:14.)

47. Ọlọrun ni o ngbẹsan mi, ti o si ṣẹgun awọn eniyan fun mi. (Psm 94:1; 47:3.)

48. O gba mi lọwọ awọn ọta mi: pẹlupẹlu iwọ gbe mi lékè ju awọn ti o dide si mi lọ; iwọ ti gba mi lọwọ awọn ọkunrin alagbara. (Psm 143:9; 27:6; 140:1,4.)

49. Nitori naa ni emi ṣe fi ìyìn fun ọ, Oluwa, ni awujọ awọn orilẹ-ede, emi o si maa kọrin iyin si orukọ rẹ. (Rom 15:9; Psm 108:1.)

50. Ẹni ti o fi ìgbàlà nla fun Ọba rẹ̀; o si fi aanu han fun Ẹni-àmìòróró rẹ̀, fun Dafidi, ati fún iru-ọmọ rẹ̀ laelae. (Psm 144:10; 28:8; 89:4,29.)

## ORIN 19.

**Ìṣẹ̀dá nfi Ogo Ọlọrun hàn.**

AWỌN ọ̀run nsọ̀rọ̀ ogo Ọlọrun; ati ofurufu nfi iṣẹ́ ọwọ́ rẹ̀ hàn. (Gen 1:6; Isa 40:22; Rom 1:19,20.)

2. Ọjọ dé ọjọ nfọhun, ati òru de òru nfi ìmọ̀ hàn. (Psm 74:16.)

3. Ko si ohùn kan tabi èdè kan, nibi ti a ko gbọ́ ìró wọn.

4. Ìró wọn la gbogbo ayé já, ati ọ̀rọ̀ wọn de opin ayé: ninu wọn ni o gbe pàgọ́ fun òòrùn. (Rom 10:18.)

5. Ti o dabi ọkọ iyawo ti njade ti ìyẹ̀wù rẹ̀ wa, ti o si yọ bi ọkunrin alagbara lati súré ìje. (Onws 1:5.)

6. Ijadelọ rẹ̀ ni lati òpin ọ̀run wá, ati àyíká rẹ̀ si de ipinlẹ rẹ̀: kò si sí ohun tí ó fi ara pamọ́ kúrò nínú ooru rẹ̀. (Psm 113:3; Deut 30:4.)

**Ọ̀rọ̀ Ọlọrun nfi agbara rẹ̀ hàn.**

7. Ofin Oluwa pé, o nyi ọkan pada: ẹ̀rí Oluwa daniloju, o nsọ òpè di ọlọgbọn. (Psm 119:142; 23:3; 93:5; 111:7; 119:98–100.)

8. Ilana Oluwa tọ́, o nmu ọkàn yọ̀: àṣẹ Oluwa ni mímọ́, o nṣe ìmọ́lẹ̀ ojú. (Psm 119:128; 12:6; 119:30.)

9. Ẹ̀rù Oluwa mọ́, pípé ni titi lae; idajọ Oluwa ni otitọ, ododo ni gbogbo wọn. (Psm 119:42.)

10. Wọn ju wura daradara pupọ; wọn si dùn ju oyin lọ, ati rírò afárá oyin. (Owe 8:10; 16:24.)
11. Pẹlupẹlu nipa wọn ni a ti sí iranṣẹ rẹ leti; ati ni pípamọ́ wọn èrè púpọ̀ nbẹ. (Psm 17:4; Owe 29:18.)
12. Tani o le mọ ìşìnà rẹ̀? Wẹ̀ mi mọ kúrò nínú ìşìṣe ìkọ̀kọ̀ mi. (Psm 139:6; 51:1,2; 90:8.)
13. Fa iranṣẹ rẹ sẹhin pẹlu kuro ninu ẹ̀sẹ̀ ikugbu: maṣe jẹ ki wọn o jọba lori mi: nigba naa ni ẹmi o duro ṣinṣin, emi o si ṣe alaijẹbi kuro ninu ẹ̀ṣẹ̀ nla. (Psm 119:33; 32:2; 25:11.)
14. Jẹ ki ọ̀rọ̀ ẹnu mi, ati ìṣàrò ọkàn mi, ṣe itẹwọgba ni ojú rẹ, Oluwa, agbára mi, ati oludande mi. (Psm 104:34; 18:2; Isa 41:14; 43:14.)

## ORIN 20.

**Adura fun Iṣẹgun.**

KI Oluwa gbohun rẹ ni ọjọ́ ipọnju; orukọ Ọlọrun Jakọbu ki o dabobo ọ. (Psm 102:2; 91:14; 36:7,11; 59:1.)
2. Ki o rán iranlọwọ si ọ lati ibi-mímọ́ wá, ki o si tì ọ lẹhin lati Sioni wa. (Psm 3:4; 119:28.)
3. Ki o rántí ẹbọ-ọrẹ rẹ gbogbo, ki o si gba ẹbọ sisun rẹ. (Psm 51:19.)
4. Ki o fi fun ọ gẹgẹ bi ti inú rẹ, ki o si mu gbogbo ìmọ̀ rẹ ṣẹ. (Psm 21:2; 145:19.)
5. Awa o maa kọrin ayọ̀ igbala rẹ, ati ni orukọ Ọlọrun wa ni awa o fi ọ̀págun wa sọlẹ̀; ki Oluwa o mu gbogbo ìbéèrè rẹ ṣẹ. (Psm 9:14; 1 Sam 1:17.)

**Idaniloju iranlọwọ Ọlọrun.**

6. Nigba yìí ni mo to mọ̀ pe Oluwa gba Ẹni-àmìòróró rẹ là; yoo gbọ lati ọ̀run mímọ́ rẹ wa nipa agbara igbala ọwọ́ ọ̀tún rẹ̀. (Psm 41:11; Isa 58:9; Psm 28:8.)
7. Awọn ẹlomiran gbẹkẹle kẹ̀kẹ́, awọn ẹlomiran le ẹṣin; ṣugbọn awa o ranti orukọ Oluwa Ọlọrun wa. (Isa 36:9; 31:1; 2 Kro 32:8.)
8. Wọn wólẹ̀, wọn si ṣubú: ṣugbọn awa dide awa si duro ṣinṣin.
9. Fi ìṣẹgun fun ọba, Oluwa, ki o sì gbọ́* nigba ti awa bá ńkigbe pe e. (Psm 3:7.)

(9) *Bibeli miran wi pe 'Gbani, Oluwa, ki Oba o gbọ́'.

## ORIN 21.

**Opẹ́ fun iṣẹgun atẹhinwa.**

OBA yoo maa yọ̀ ni agbara rẹ, Oluwa; ati ni igbala rẹ, yoo ti yọ̀ pẹ tó! (Psm 59:16,17; 9:14.)
2. 'Iwọ ti fi ìfẹ́ ọkàn rẹ̀ fun un, iwọ ko si du u ni ibeere ẹnu rẹ̀. (Psm 37:4.)
3. Nitori iwọ ti fi ibukun ọrẹ ko o lọna, iwọ fi adé kìkì wura de e ni orí. (Psm 59:10.)
4. O tọrọ ẹmi lọwọ rẹ, iwọ si fi fun un, ani ọjọ gigun lae, ati laelae. (Psm 133:3; 91:16.)
5. Ogo rẹ̀ pọ̀ nipa igbala rẹ: ìyìn ati ọlanla ni ìwọ fi si i lara. (Psm 18:50; 45:3,4.)
6. Nitori iwọ ti ṣe e ni ẹni-ibukun fún jùlọ títí ayé: iwọ si fi ojú rẹ mu un yọ̀ gidigidi. (1 Kro 17:27; Psm 16:11.)
7. Nitori ti ọba gbẹkẹle Oluwa, ati nipa aanu Ọga-ogo ki yoo ṣipo pada. (2 A.Ọba 18:5; Psm 16:8.)

**Idaniloju fun iṣẹgun ti nbọ.**

8. Ọwọ́ rẹ yoo wá gbogbo awọn ọta rẹ rí: ọwọ́ ọ̀tún rẹ ni yoo wá awọn ti o korira rẹ ri. (Isa 10:10.)
9. Iwọ o ṣe wọn bi ileru oníná ni igba ibinu rẹ: Oluwa yoo gbe wọn mì ni ibinu rẹ̀: iná naa yoo si jo wọn pa. (Mal 4:1; E.Jer. 2:2.)
10. Eso wọn ni iwọ o run kurò ni ilẹ̀, ati iru-ọmọ wọn kuro ninu awọn ọmọ eniyan. (Deut 28:18; Psm 37:28.)
11. Nitori ti wọn nro ibi sí ọ: wọn npete ìwà-ibi, ti wọn ki yoo lè ṣe. (Psm 2:1–3; 10:2.)
12. Nitori naa ni iwọ o ṣe mu wọn pẹhinda, nigba ti iwọ ba fi ọfà rẹ wọn

ọ̀kánkán ojú wọn. (Psm 18:40; 7: 12,13.)

13. Ki iwọ o maa lékè, Oluwa, ni agbara rẹ; bẹẹ ni awa o maa kọrin, ti awa o si maa yin agbara rẹ. (Psm 57:5; 81:1.)

ORIN 22.

**Ìkọ̀sílẹ̀: (Asotẹ́lẹ̀ iku Messiah).**

OLỌRUN mi, Ọlọrun mi, eeṣe ti iwọ fi kọ̀ mi silẹ? Ti iwọ si jìnnà si igbala mi, ati si ohun igbe mi? (Matt 27:46; Psm 10:1.)

2. Ọlọrun mi, emi nkigbe ni ọ̀sán, ṣugbọn iwọ kò dahun: ati ni igba òru emi ko dakẹ. (Psm 42:3.)

3. Ṣugbọn mimọ ni Iwọ, ẹni ti o tẹ ìyìn Israẹli dó. (Psm 99:9; 35:8.)

4. Awọn baba wa gbẹkẹle ọ: wọn ni ìgbẹkẹle, iwọ si gba wọn.

5. Wọn kigbe pe ọ, a si gbà wọn: wọn gbẹkẹle ọ, wọn kò si daamu. (Psm 107:6; 25:2,3; Rom 9:33.)

**Ẹni ti awọn eniyan ngan.**

6. Ṣugbọn kokoro ni emi, ki si ṣe eniyan; ẹ̀gàn awọn eniyan, ati ẹlẹ́yà awọn eniyan. (Job 25:6; Isa 41:14: Psm 31:11; Isa 49:7.)

7. Gbogbo awọn ti o ri mi nfi mi rẹrin ẹlẹ́yà: wọn nyọ ṣuti ètè wọn, wọn nmi orí pe. (Matt 27:39; Mk 15:29.)

8. "O gbẹkẹle Oluwa, jẹ ki o gba a la; jẹ ki o gba a la nitori inu rẹ̀ dun si i." (Matt 27:43; Mk 1:11.)

9. Ṣugbọn iwọ ni ẹni ti o mu mi jade lati inú wá: iwọ ni o mu mi wà ni ailewu, nigba ti mo rọ̀ mọ́ ọmú ìyá mi. (Psm 71:6.)

10. Iwọ ni a ti fi mi le lọwọ lati inu iya mi wá: iwọ ni Ọlọrun mi lati inu iya mi wa. (Isa 46:3.)

11. Máṣe jinna si mi; nitori ti ìyọnu sunmọ etílé; nitori ti kò si oluranlọwọ. (Psm 72:12.)

**Iyika akọ-malu Baṣani.**

12. Akọ-malu pupọ ni o yi mi ka: malu Baṣani ti o lagbara rọ̀gbà yi mi ka. (Psm 68:30; Deut 32:14.)

13. Wọn ya ẹnu wọn si mi, bi kinniun ti ndọdẹ kiri, ti nke ramú-ramù. (Psm 35:21; 17:12.)

14. A tu mi danu bi omi, gbogbo egungun mi si yẹ̀ lori iké: ọkàn mi dabi idà; ó yọ laarin inu mi. (Job 30:16; Psm 31:10; 107:26.)

15. Agbara mi di gbígbẹ bi àpáàdì: ahọ́n mi si lẹ̀ mọ mi ni ẹ̀rẹ̀kẹ̀; iwọ mu mi dubulẹ ninu erùpẹ̀ ikù. (Psm 38:10; 137:6; 104:29.)

**Wọn gún ọwọ́ rẹ̀, wọn si ṣẹ gègé le aṣọ-ileke rẹ̀.**

16. Nitori ti awọn ajá yi mi ká: ijọ awọn eniyan buburu ti ká mi mọ́; wọn gun mi lọwọ, wọn si gun mi lẹsẹ̀. (Psm 59:6; Matt 27:35.)

17. Mo lè kàye gbogbo egungun mi: awọn tikarawọn nwò, wọn doju le mi.

18. Wọn pin aṣọ mi fun ara wọn, wọn si ṣẹ́ gègé le aṣọ-ileke mi. (Matt 27:35.)

**O gbadura fun iranlọwọ.**

19. Ṣugbọn iwọ máṣe jinna si mi, Oluwa: agbara mi, yara lati ràn mi lọwọ. (ẹsẹ 11; Psm 70:5.)

20. Gba ọkàn mi lọwọ idà; ati ẹmi mi kannaa lọwọ agbara ajá naa. (Psm 35:17.)

21. Gba mi kuro ninu ẹnu kinniun; ki iwọ si gbohun mi lati ibi ìwo awọn agbanrerè. (ẹsẹ 13; Psm 34:4.)

**Ìyìn fun Ọlọrun.**

22. Emi o sọrọ orukọ rẹ fun awọn arakunrin mi: ni awujọ ni emi o maa yìn ọ. (Heb 2:12.)

23. Ẹyin ti o bẹru Oluwa, ẹ yin in, gbogbo ẹ̀yin irú-ọmọ Jakọbu, ẹ yin in logo: ki ẹ si maa bẹ̀rù rẹ gidigidi, gbogbo ẹ̀yin iru-ọmọ Israẹli. (Psm 135:19; 86:12; 33:8.)

24. Nitori ti ko kẹ́gàn, bẹẹ ni ko korira ipọnju awọn olupọnju; bẹẹ ni kò pa oju rẹ̀ mọ́ kuro lara rẹ̀; ṣugbọn nigba ti o kigbe pe e, o gbọ. (Psm 102:17; 69:17; Heb 5:7.)

25. Nipa tirẹ ni ìyìn mi yoo wa ninu

ajọ nla, emi o san ẹ̀jẹ́ mi niwaju awọn ti o bẹ̀rù rẹ̀. ( Psm 35:18; 66:13.)

**Gbogbo eniyan ni a fi igbala lọ.**

26. Awọn olupọnju yoo jẹ, yoo tẹ wọn lọrun: awọn ti nwa Oluwa yoo yin in: ọkàn yin yoo wà laelae. ( Psm 107:9; 40:16; 69:32.)

27. Gbogbo òpin ayé ni yoo ranti, wọn o si yipada si Oluwa: ati gbogbo ìbátan orilẹ-èdè ni yoo wolẹ-sìn niwaju rẹ̀. ( Psm 2:8; 86:9.)

28. Nitori ijọba ni ti Oluwa; oun si ni o npaṣẹ lori awọn orilẹ-ède. ( Psm 47:7,8; Matt 6:13.)

29. Gbogbo awọn ti o sanra ni ayé yoo maa jẹ, wọn o si maa wolẹ-sìn; gbogbo awọn ti nsọkalẹ lọ sinu erùpẹ̀ yoo tẹriba niwaju rẹ̀, ati ẹni ti kò le pa ọkàn ara rẹ̀ mọ́ ni ààyè. ( Psm 47:7; Isa 27:13; Psm 95:6.)

30. Irú kan yoo maa sin in; a o si ka a ni ìran kan fun Oluwa. ( Psm 102:28; 71:18.)

31. Wọn o wá, wọn o si maa sọ̀rọ̀ ododo rẹ̀ fun awọn eniyan kan ti a o bi, pé; oun ni o ṣe èyìí. ( Psm 78:6.)

## ORIN 23.

**Oluwa nbọ́, o si nṣọ́ awọn agutan Rẹ̀.**

OLUWA ni Oluṣọ-agutan mi; emi ki yoo ṣe alaini. (Isa 40:11; Jer 23:4; Jhn 10:11; 1 Pet 2:25; Filp 4:19.)

2. O mu mi dubulẹ ninu pápá-oko tútù; o mu mi lọ si ìhà omi dídákẹ́ rọ́rọ́. (Esk 34:14; Ifh 7:17.)

3. O tu ọkan mi lara; o mu mi lọ nipa ọ̀nà ododo nitori orukọ rẹ̀. ( Psm 19:7; 5:8; 85:13; 143:11.)

4. Nitootọ, bi mo tilẹ nrin laarin àfonífojì òjìji ikú, emi ki yoo bẹ̀rù ibi kan; nitori ti Iwọ pẹlu mi; ogọ rẹ ati ọpa rẹ wọn ntu mi ninu. ( Psm 138:7; Job 3:5; Psm 27:1; Isa 43:2.)

**Oluwa yoo bukun awọn eniyan rẹ̀.**

5. Iwọ tẹ tabili ounjẹ silẹ niwaju mi ni ojú awọn ọta mi; iwọ da ororo si mi ni ori; ago mi si kun àkúnwọ́sílẹ̀. ( Psm 78:19; 31:19; 92:10; 16:5.)

6. Nitootọ, ire ati aanu ni yoo maa tọ mi lẹhin ni ọjọ́ ayé mi gbogbo; emi o si maa gbe inu ilé Oluwa laelae. ( Psm 25:7–10; 27:4–6.)

## ORIN 24.

**Ọlọrun, Ẹlẹda ohun gbogbo.**

TI Oluwa ni ilẹ, ati ẹ̀kún rẹ̀; ayé, ati awọn ti o tẹdo sinu rẹ̀. (Eks 9:29; Job 41:11; 1 Kor 10:26; Psm 89:11.)

2. Nitori ti o fi idi rẹ̀ sọlẹ̀ lori òkun, o si gbe e kalẹ̀ lori awọn ìṣàn-ọmi.

**Ihuwasi awọn eniyan Ọlọrun.**

3. Tani yoo gun ori òke Oluwa lọ? Tabi tani yoo duro ni ibi mimọ rẹ? ( Psm 15:1; 2:6; 65:4.)

4. Ẹni ti o ni ọwọ mímọ́, ati àyà funfun: ẹni ti kò gbe ọkàn rẹ̀ soke si asán, ti kò si bura ẹ̀tàn. (Job 17:9; Matt 5:8; Psm 15:4.)

5. Oun ni yoo ri ibukun gba lọwọ Oluwa, ati ododo lọwọ Ọlọrun igbala rẹ̀. (Deut 11:26,27; Isa 46:13; Psm 25:5.)

6. Èyí ni ìran awọn ti nṣe afẹri rẹ̀, ti nṣe afẹri rẹ, Ọlọrun Jakọbu. ( Psm 27:8.)

**Wiwole Ọba Ogo.**

7. Ẹ gbé orí yin soke, ẹ̀yin ẹnu-ọ̀nà; ki a si gbe yin soke, ẹ̀yin ilẹkun ayéraye: ki Ọba ogo o wọ inu ile wá. (Isa 26:2; 1 Kor 2:8.)

8. Tani Ọba ogo yìí? Oluwa ti o le, ti o si lagbara, Oluwa ti o lagbara ni ogun. ( Psm 89:13; 76:3–6.)

9. Ẹ gbe orí yin soke, ẹ̀yin ẹnu-ọ̀nà; àní ki ẹ gbe wọn soke, ẹ̀yin ilẹkun ayeraye: ki Ọba ogo o wọ inu ile wá. (Sek 9:9; Matt 21:5.)

10. Tani Ọba ogo yìí? Oluwa awọn ọmọ-ogun; oun naa ni Ọba ogo.

## ORIN 25.

**Wíwá ọ̀nà Ọlọrun.**

OLUWA, iwọ ni mo gbe ọkan mi soke si. ( Psm 86:4.)

2. Ọlọrun mi, emi gbẹkẹle ọ: máṣe jẹ ki ojú o ti mi, máṣe jẹ ki awọn ọta mi o yọ̀ mi. ( Psm 31:6; 41:11.)

3. Lootọ, máṣe jẹ ki ojú o ti ẹnikẹni ti o duro ti ọ: awọn ti nṣè ni ainidi ni ojú yoo ti. (Isa 49:23; 33:1.)
4. Fi ọ̀nà rẹ hàn mi, Oluwa; kọ mi ni ipa tirẹ. (Psm 5:8; 86:11.)
5. Sin mi ni ọ̀nà otitọ rẹ, ki o si kọ́ mi: nitori iwọ ni Ọlọrun igbala mi; iwọ ni mo duro ti lọjọ gbogbo. (Jhn 16:13; Psm 24:5; 40:1.)
6. Oluwa, ranti aanu ati iṣeun-ifẹ rẹ; nitori ti wọn ti wa ni igba atijọ. (Psm 103:17; Isa 63:15.)
7. Maṣe ranti ẹ̀ṣẹ̀ igbà-èwe mi, ati irekọja mi: gẹgẹ bi aanu rẹ iwọ ranti mi, Oluwa, nitori oore rẹ. (Job 13:26; Jer 3:25; Psm 51:1.)

**Ọna Ọlọrun ni a fi hàn gbangba.**

8. Rere ati diduro-ṣinṣin ni Oluwa: nitori naa ni yoo ṣe maa kọ́ ẹlẹṣẹ ni ọ̀nà naa. (Psm 106:1; 92:15; 32:8.)
9. Onirẹlẹ ni yoo tọ́ si ọ̀nà tootọ, ati onirẹlẹ ni yoo kọ́ ni ọ̀nà rẹ̀. (Psm 23:3; 27:11.)
10. Gbogbo ipá Oluwa ní aanu ati otitọ, fun irú awọn ti o pa majẹmu rẹ̀ ati ẹ̀rí rẹ̀ mọ. (Psm 40:11; 103:18.)
11. Nitori orukọ rẹ, Oluwa, dari ẹ̀bi ẹ̀ṣẹ̀ mi ji mi, nitori tí o tobi. (Psm 31:1; Rom 5:20.)
12. Ọkunrin wo ni o bẹ̀rù Oluwa? Oun ni yoo kọ́ ni ọ̀nà ti yoo yàn.
13. Ọkàn rẹ̀ yoo jókòó ninu ire, irú-ọmọ rẹ̀ yoo si jogun ayé. (Owe 19:23; Psm 37:11.)
14. Aṣiri Oluwa wà pẹlu awọn ti o bẹru rẹ̀, yoo si fi wọn mọ majẹmu rẹ̀. (Owe 3:32; Jhn 7:17.)
15. Oju mi gbe soke si Oluwa lae; nitori ti yoo fa ẹsẹ̀ mi yọ kuro ninu àwọ̀n naa. (Psm 141:8.)

**Adura fun Igbala.**

16. Yipada si mi, ki o si ṣaanu fun mi; nitori ti mo di òfo, mo si di olupọnju. (Psm 69:16.)
17. Iṣẹ́ àyà mi di pupọ: mu mi jade ninu ipọnju mi. (Psm 88:3; 107:6.)
18. Wo ipọnju mi ati irora mi; ki o si dari gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ mi ji mi; (2 Sam 16:22.)
19. Wọ awọn ọta mi, bi wọn ti pọ̀ tó; wọn si korira mi ni irira ìkà. (Psm 3:1; 27:12.)
20. Pa ọkàn mi mọ, kí o si gbà mi: máṣe jẹ ki ojú ti mi; nitori mo gbẹkẹ mi le ọ. (Psm 86:2.)
21. Jẹ ki ìwà-titọ ati iduro-ṣinṣin o pa mí mọ́: nitori ti mo duro ti ọ. (Psm 41:12; ẹsẹ 3.)
22. Ra Israẹli pada, Ọlọrun, kuro ninu iṣẹ́ rẹ̀ gbogbo. (Psm 130:8.)

## ORIN 26.

**Adura fun Iranlọwọ ti Ọlọrun.**

SE idajọ mi, Oluwa; nitori ti mo ti nrìn ninu ìwà titọ mi; emi ti gbẹkẹle Oluwa pẹlu; njẹ ẹsẹ̀ mi ki yoo yẹ̀. (Psm 7:8; Owe 20:7; Psm 25:2; Heb 10:23.)
2. Wadi mi, Oluwa, ki o si ridi mi; dán inu mi ati ọkàn mi wò. (Psm 7:9; 66:10.)
3. Nitori ti iṣeun-ìfẹ́ rẹ nbẹ niwaju mi: emi si ti nrìn ninu otitọ rẹ. (2 A.Ọba 20:3.)

**Dafidi gbeja ara rẹ̀.**

4. Emi ko ba ẹni asán jókòó, bẹẹ ni emi ki yoo ba awọn alayidayida wọle. (Psm 1:1.)
5. Emi ti korira ijọ awọn olùṣe-buburu; emi ki yoo si ba awọn eniyan buburu jókòó. (Psm 139:21; 1:1.)
6. Emi o wẹ ọwọ́ mi ni ailẹ́ṣẹ̀: bẹẹ ni emi o si yi pẹpẹ rẹ ká, Oluwa. (Psm 73:13.)
7. Emi yoo gbe ohùn ọpẹ́ soke, emi yoo si maa sọrọ gbogbo iṣẹ́ iyanu rẹ̀. (Psm 35:18; 9:1.)

**Ẹbẹ ti Dafidi bẹ gbẹhin fun iranwọ.**

8. Oluwa, emi ti nfẹ ibugbe ile rẹ, ibi agọ ọlá rẹ. (Psm 27:4.)
9. Máṣe ko ọkàn mi pọ pẹlu awọn ẹlẹ́ṣẹ̀, tabi ẹmi mi pẹlu awọn eniyan-ẹ̀jẹ̀. (Psm 28:3.)
10. Ni ọwọ́ ẹni ti ìwà-ìkà nbẹ, ọwọ́

ọtún wọn si kún fún àbẹ̀tẹ́lẹ̀. (1 Sam 8:3.)

11. Ṣugbọn bi o ṣe temi, emi o maa rin ninu ìwàtítọ́ mi: rà mi pada, ki o si ṣàánú fun mi. (ẹsẹ 1; Psm 69:18.)

12. Ẹsẹ̀ mi duro ni ibi títẹ́jú: ninu awọn ijọ ni emi o maa fi ibukun fun Oluwa. ( Psm 40:2; 27:11; 22:22.)

ORIN 27.

**Orin igbẹkẹle Dafidi.**

OLUWA ni imọlẹ mi ati igbala mi; tani emi o bẹ̀rù? Oluwa ni agbara ẹmi mi; àyà tani yoo fò mi? (Isa 60:19; Ẹks 15:2; Psm 62:2.)

2. Nigba ti awọn eniyan buburu, ani awọn ọta mi ati awọn abinuku mi súnmọ́ mi lati jẹ ẹran ara mi, wọ́n kọsẹ̀, wọn si ṣubú. ( Psm 14:4.)

3. Bi ogun tilẹ dóti mi, aya mi ki yoo fo: bi ogun tilẹ dide si mi, ninu èyí ni ọkan mi yoo le. ( Psm 3:6.)

4. Ohun kan ni emi ntọrọ lọdọ Oluwa, oun naa ni emi o maa wakiri: ki emi le maa gbe inu ile Oluwa lọjọ ayé mi gbogbo, ki emi lè maa wo ẹwà Oluwa, ki emi si maa fi inudídùn wo tẹmpili rẹ̀. ( Psm 26:8; 90:17.)

5. Nitori pe ni igba ipọnju oun o pa mi mọ ninu àgọ́ rẹ̀: ni ibi ìkọ̀kọ̀ àgọ́ rẹ̀ ni yoo pa mi mọ́; yoo si gbé mi soke ka orí apata. (Psm 31:20; 40:2.)

6. Nigba yìí ni ori mi yoo gbe soke ga ju awọn ọta mi lọ, ti o yi mi ká: nitori naa ni emi o ṣe rubọ ayọ̀ ninu agọ rẹ̀; emi o kọrin, nitootọ emi o kọrin ìyìn sí Oluwa. ( Psm 3:3.)

**Adura Dafidi fun iranlọwọ.**

7. Gbọ́, Oluwa, nigba ti mo ba fi ohun mi pè: ṣaanu fun mi pẹlu, ki o si da mi lóhùn. ( Psm 39:12; 13:3.)

8. Nigba ti o wi pe, "Ẹ maa wa ojú mi;" ọkàn mi wi fun ọ pe, "Ojú rẹ, Oluwa, ni emi o maa wá." ( Psm 24:6.)

9. Máṣe pa ojú rẹ mọ kuro lọdọ mi; maṣe fi ibinu ṣa iranṣẹ rẹ tì: iwọ ni o ti nṣe iranlọwọ mi; ma fi mi silẹ, bẹẹ ni ki o máṣe kọ̀ mí, Ọlọrun igbala mi. ( Psm 69:17.)

10. Nigba ti baba ati ìyá mi kọ̀ mi silẹ, nigba naa ni Oluwa yoo tẹ́wọ́ gba mi. (Isa 49:15; 40:11.)

11. Kọ́ mi ni ọ̀nà rẹ, Oluwa, ki o si tọ mi ni ọna títọ́, nitori awọn ọta mi. ( Psm 25:4; 86:11; 5:8.)

12. Máṣe fi mi lé ifẹ awọn ọta mi lọwọ; nitori awọn ẹlẹri èké dide si mi, ati irú awọn ti nmi ìmí-ìkà. ( Psm 41:2; 35:11; Matt 26:60; A.A. 9:1.)

13. Ṣugbọn emi ti gbagbọ lati ri ire Oluwa ni ilẹ̀ alààyè. ( Psm 31:19; Jer 11:19.)

14. Duro de Oluwa; ki o si tujuka, yoo si mu ọ ni àyà le: mo ni, duro de Oluwa. ( Psm 40:1; Jos 1:6.)

ORIN 28.

**Adura fun iranwọ.**

IWỌ, Oluwa, apata mi ni emi o kigbe pè, máṣe dákẹ́ si mi; bi iwọ ba dakẹ si mi, emi o dabi awọn ti o lọ sinu ihò. ( Psm 83:1; 88:4.)

2. Gbọ ohun ẹ̀bẹ̀ mi, nigba ti mo ba nkigbe pe ọ, nigba ti mo ba gbe ọwọ́ mi soke siha ibi-mimọ julọ rẹ. ( Psm 140:6; 5:7; 138:2.)

3. Maṣe fà mi lọ pẹlu awọn eniyan buburu, ati pẹlu awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ̀, ti nsọrọ alaafia si aladugbo wọn, ṣugbọn ìwà-ìkà nbẹ ni ọkàn wọn. ( Psm 26:9; 12:2; Jer 9:8.)

4. Fi fun wọn gẹgẹ bi iṣẹ wọn, ati gẹgẹ bi iwa buburu ètè wọn, fi fun wọn nipa iṣẹ́ ọwọ́ wọn, fi èrè wọn fun wọn. (Ifh 18:6.)

5. Nitori ti wọn kò ka iṣẹ́ Oluwa sí, tabi iṣẹ́ ọwọ́ rẹ̀; oun o run wọn, ki yoo si gbé wọn ró. (Isa 5:12.)

**Idaniloju fun idahun.**

6. "Olubukun ni Oluwa", nitori ti o ti gbọ ohùn ẹ̀bẹ̀ mi. ( Psm 116:1.)

7. Oluwa ni agbara ati asà mi; oun ni àyà mi gbẹkẹle, bayìí ni a si nran mi lọwọ; inu mi si dùn jọjọ: pẹlu orin mi

ni mo nfi ọpẹ́ fún un. (Psm 18:2; 13:5.)

8. Oluwa ni agbara awọn eniyan rẹ̀, oun si ni agbara igbala ẹni-àmìòróró rẹ̀. (Psm 20:6.)

9. Gba awọn eniyan rẹ là, ki o si busi ilẹ-ini rẹ: maa bọ́ wọn pẹlu, ki o si maa gbe wọn lékè laelae. (Deut 9:29; Esra 1:4.)

ORIN 29.

**Dafidi paṣẹ fun awọn eniyan lati maa yin Ọlọrun logo.**

Efi fun Oluwa, ẹ̀yin ọmọ awọn alagbara, ẹ fi ogo ati agbara fun Oluwa. (1 Kro 16:28,29; Psm 96: 7–9.)

2. Ẹ fi fun Oluwa ogo, ti o yẹ fun orukọ rẹ̀; ẹ maa sin Oluwa ninu ẹwà-ìwà-mimọ. (2 Kro 20:21.)

**Agbara Ọlọrun ninu ìjì.**

3. Ohùn Oluwa nbẹ lori omi púpọ̀; Ọlọrun ogo nsán ààrá: Oluwa nbẹ lori omi púpọ̀. (Job 37:4,5.)

4. Ohun Oluwa ni agbara; ohun Oluwa ni ọlanla. (Psm 68:33.)

5. Ohùn Oluwa nfa igi kedari ya; lootọ, Oluwa nfa igi kedari Lebanoni ya. (Isa 2:13.)

6. O mu wọn fò pẹlu ọmọ-malu; Lebanoni ati Sirioni bi ọmọ agbanrere. (Deut 3:9; Psm 114:4.)

7. Ohùn Oluwa nkọ ọ̀wọ́ iná mànà.

8. Ohùn Oluwa nmi aginju; Oluwa nmi aginju Kadesi. (Num 13:26.)

9. Ohùn Oluwa ni o nmu abo àgbọ̀nrín bí, o si fi igbó dídí hàn: ati ninu tẹmpili rẹ̀ ni olukuluku nkigbe Ogo." (Psm 26:8.)

**Adura fun ibukun Oluwa fun ìjì Òkun.**

10. Oluwa jókòó lori ìṣàn-omi; nitootọ, Oluwa jókòó bi Ọba laelae (Psm 10:16.)

11. Oluwa yoo fi agbara fún awọn eniyan rẹ̀; Oluwa yoo fi alaafia bùsi i fun awọn eniyan rẹ̀. (Psm 28:8; 37: 11.)

ORIN 30.

**Adura fun ìgbàlà.**

EMI o kokiki rẹ, Oluwa; nitori iwọ ni o gbé mi leke, ti iwọ ko si jẹ ki awọn ọ̀tá mi o yọ̀ mí. (Psm 28:9; 25:2.)

2. Oluwa Ọlọrun mi, emi kigbe pe ọ, iwọ si ti mu mi lara da. (Psm 88:13; 6:2.)

3. Oluwa, iwọ ti yọ ọkàn mi jade kuro ninu isà-òkú: iwọ o si pa mi mọ́ lááyè, ki emi má baa lọ sinu ihò. (Psm 86:13; 28:1.)

**Ìpè si awọn eniyan lati yin Ọlọrun logo.**

4. Kọrin si Oluwa, ẹ̀yin eniyan rẹ̀ mimọ́, ki ẹ si maa dupẹ ni iranti ìwà-mimọ rẹ̀. (Psm 149:1; 50:5; 97:12.)

5. Nitori pe, ni iṣẹju kan ni ibinu rẹ̀ npẹ́, ni ojurere rẹ̀ ni ìyè gbé wà; bi ẹkún tilẹ̀ pẹ di alẹ́, ṣugbọn ayọ̀ nbọ ni owurọ. (Psm 103:9; 63:3.)

6. Ati ninu alaafia mi, emi ni, "ipò mi ki yoo pada laelae."

7. Oluwa, nipa ojú-rere rẹ, iwọ ti mu òkè mi duro ṣinṣin: nigba ti iwọ pa oju rẹ mọ́, iyọnu dé bá mi.

8. Emi kigbe pe ọ, Oluwa; ati si Oluwa ni emi nbẹ̀bẹ̀ gidigidi.

9. "Èrè kinni o wa ni ẹ̀jẹ̀ mi, nigba ti mo ba lọ sinu ihò? Erupẹ ni yoo maa yìn ọ́ bí? Oun ni yoo maa sọ̀rọ̀ otitọ rẹ bi? (Psm 6:5.)

10. Gbọ́, Oluwa, ki o si ṣaanu fun mi: Oluwa, iwọ maa ṣe oluranlọwọ mi."

11. Iwọ ti sọ ikaanu mi di ijó fun mi; iwọ ti bọ aṣọ-ọ̀fọ̀ mi kuro, iwọ si fi ayọ̀ di mi ni amure. (Psm 6:8; Jer 31:4,13; Psm 4:7.)

12. Nitori ìdí eyi ni ki ogo mi maa

korin si ọ, ki o má si ṣe dákẹ́. Oluwa Ọlọrun mi, emi o maa fi ìyìn fun ọ laelae. (Psm 16:9; 44:8.)

## ORIN 31.

**Igbẹkẹle ninu Ọlọrun ati adura fun igbala.**

OLUWA, iwọ ni mo gbẹkẹ mi le: máṣe jẹ ki ojú o ti mi: gba mi ninu ododo rẹ. (Psm 22:5; Isa 49:23.)

2. Dẹ eti rẹ silẹ si mi: gbà mi nisinsinyìí: iwọ maa ṣe apata agbara mi, ileàábò lati gba mi sí. (Psm 71:2.)

3. Nitori iwọ ni apata mi ati odi mi: nitori naa, nitori orukọ rẹ maa tọ́ mi, ki o si maa ṣe amọ̀nà mi. (Psm 18:2; 23:3.)

4. Yọ mi jade ninu àwọ̀n ti wọn nà silẹ fun mi ni ìkọ̀kọ̀: nitori iwọ ni ààbò mi. (Psm 25:15; 28:8.)

5. Ni ọwọ́ rẹ ni mo fi ẹ̀mí mi lé: ìwọ ni o ti ra mi padà, Oluwa Ọlọrun otitọ. (Luk 23:46; A.A. 7:59.)

6. Emi ti korira awọn ẹni ti nfiyesi èké asán: ṣugbọn emi gbẹkẹle Oluwa. (Jona 2:8.)

7. Emi o yọ̀, inu mi yoo si dùn ninu aanu rẹ: nitori ti iwọ ti ro ti ìṣẹ́ mi; iwọ ti mọ ọkàn mi ninu ipọnju. (Psm 90:14; Jhn 10:27.)

8. Iwọ kò si sé mi mọ́ si ọwọ́ ọ̀tá: iwọ fi ẹsẹ̀ mi tẹlẹ̀ ni ibi àyè nla. (Deut 32:30; Psm 4:1.)

**Idande kuro ninu ìṣoro.**

9. Ṣaanu fun mi, Oluwa, nitori ti emi wa ninu ìṣẹ́: ojú mi run fun ìbànújẹ́, ọkan mi ati inu mi. (Psm 6:7.)

10. Emi fi ibanujẹ lo ọjọ́ mi, ati ọdún mi pẹlu ìmí-ẹ̀dùn: agbara mi kú nitori ẹ̀ṣẹ̀ mi, awọn egungun mi si run. (Psm 13:2; 39:11; 38:3.)

11. Emi di ẹni-ẹ̀gàn laarin awọn ọ̀tá mi gbogbo, pẹlupẹlu laarin awọn aladugbo mi, mo si di ohun ẹ̀rù fun awọn ojulumọ mi: awọn ti o ri mi lode nyẹra fun mi. (Isa 53:4; Psm 38:11.)

12. Emi ti di ẹni-igbagbe kúrò ni ìyè bi òkú; emi dàbí ohun-èlò fífọ́. (Psm 88:4,5.)

13. Nitori ti emi ti ngbọ ẹ̀gàn ọ̀pọ̀ eniyan: ẹ̀rù wa nihà gbogbo: nigba ti wọn ngbìmọ̀ pọ̀ si mi, wọn gbèrò lati gba ẹ̀mí mi kuro. (Jer 20:10; E.Jer. 2:20; Matt 27:1.)

14. Ṣugbọn emi gbẹkẹle ọ, Oluwa; emi ni, "Iwọ ni Ọlọrun mi." (Psm 140:6.)

15. Igba mi nbẹ ni ọwọ rẹ: gbà mi lọwọ awọn ọ̀tá mi, ati lọwọ awọn ti nṣe inunibini si mi. (Job 24:1; Psm 143:9.)

16. Ṣe ojú rẹ ki o mọ́lẹ̀ si iranṣẹ rẹ lara: gba mi nitori aanu rẹ. (Num 6:25; Psm 4:6.)

17. Máṣe jẹ ki oju o tì mi, Oluwa; nitori ti emi nkepe ọ; eniyan buburu ni kí ojú o ti, awọn ni ki a mu dakẹ ni isà-òkú. (Psm 25:2,3.)

18. Awọn ètè èké ni ki a mu dákẹ́; ti nsọrọ ohun buburu ni igberaga ati ni ẹ̀gàn si awọn olódodo. (Psm 120:2; 94:4.)

**Ìyìn fun Ọlọrun Olugbala.**

19. Oore rẹ ti tobi to, ti iwọ fi silẹ de awọn ti o bẹ̀rù rẹ: oore ti iwọ ti ṣe fun awọn ti o gbẹkẹle ọ niwaju awọn ọmọ eniyan! (Isa 64:4; Rom 11:22; Psm 5:11.)

20. Iwọ o pa wọn mọ́ ni ibi ìkọ̀kọ̀ iwaju rẹ kuro ninú idimọlu awọn eniyan; iwọ o pa wọn mọ ni ìkọ̀kọ̀ ninu àgọ́ kan kuro ninu ìjà ahọ́n. (Psm 27:5; Job 5:21.)

21. Olubukun ni Oluwa; nitori ti o ti fi iṣeun-ifẹ rẹ̀ hàn mi ni ilu olodi. (Psm 17:7; 1 Sam 23:7.)

22. Nitori ti mo ti wi ni ikanju mi pe, "A ge mi kuro niwaju rẹ:" Ṣugbọn iwọ gbọ ohùn ẹ̀bẹ̀ mi nigba ti mo ké pè ọ. (Psm 116:11; E.Jer. 3:54.)

23. Ẹ fẹ́ Oluwa, gbogbo ẹyin eniyan rẹ̀ mimọ: Oluwa npa onigbagbọ mọ́, o si san an lọpọlọpọ fun ẹni ti nṣe igberaga. (Psm 34:9; 145:20; 94:2.)

24. Ẹ tújúká, yoo si mu yin ni àyà le, gbogbo ẹ̀yin ti o ni ìrètí ni ti Oluwa. (Psm 27:14.)

## ORIN 32.

**Ibukun wa fun awọn ti ó dárí irekọja wọn jì.**

IBUKUN ni fun awọn ti a dárí irekọja wọn jì, ti a bọ ẹ̀ṣẹ̀ wọn mọ́lẹ̀. (O.D. 85:2.)

2. Ibukun ni fun ọkunrin naa ẹni ti Oluwa ko ka ẹ̀ṣẹ̀ si lọ́rùn, ati ninu ẹ̀mí ẹni ti ẹ̀tàn kò si. (2 Kor 5:19; Jhn 1:47.)

**Ìjẹ́wọ́ ati idariji ẹ̀ṣẹ̀.**

3. Nigba ti mo dákẹ́, egungun mi di gbígbó nitori igbe mi ní gbogbo ọjọ. (Psm 39:2,3; 31:10; 38:8.)

4. Nitori ni ọ̀sán ati ni òru, ọwọ́ rẹ wuwo si mi lara: omi ara mi si dabi ọ̀dá ẹ̀rùn.

5. Emi jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ mi fun ọ, ati ẹ̀ṣẹ̀ mi ni emi kò si fi pamọ́. Emi wi pe, "Emi o jẹwọ irekọja mi fun Oluwa: "iwọ si dari ẹbi ẹ̀ṣẹ̀ mi jì. (Lef 26:40; Job 31:33; Owe 28:13; Psm 103:7.)

6. Nitori èyí ni olukuluku ẹni iwa-bi-ọlọrun yoo maa gbadura si ọ ni igba ti a le ri ọ: nitootọ ninu ìṣàn-omi nla, wọn ki yoo sunmọ ọ̀dọ̀ rẹ̀. (Psm 69:13; 144:7; Isa 43:2.)

7. Iwọ ni ibi ìpamọ́ mi: iwọ o pa mi mọ́ kuro ninu iṣẹ́; iwọ o fi orin igbala yi mi ka kiri. (Psm 31:20; 121:7; Eks 15:1.)

**Ọ̀rọ̀ ìyànjú si awọn ẹlẹṣẹ lati ronupiwada.**

8. Emi o fi ẹsẹ̀ rẹ le ọ̀nà, emi o si tọ ọ si ọ̀nà ti iwọ o rin: emi o maa fi ojú mi tọ́ ọ. (Psm 25:8; 33:18.)

9. Ki ẹ̀yin máṣe dabi ẹṣin tabi ibaka, ti ko ni iyè ninu: ẹnu ẹni ti a ko le ṣaifi ijanu bọ̀, ki wọn má baa sunmọ ọn. (Jak 3:3.)

10. Ọ̀pọ̀ ikaanu ni yoo wà fun eniyan buburu: ṣugbọn ẹni ti o ba gbẹkẹle Oluwa, aanu ni yoo yi i ka. (Rom 2:9; Owe 16:20.)

11. Ki inu yin o dun ni ti Oluwa, ẹ si maa yọ̀, ẹ̀yin olododo; ẹ si maa kọrin fún ayọ̀, gbogbo ẹ̀yin ti àyà yin duro ṣinṣin. (Psm 64:10.)

## ORIN 33.

**Ọ̀rọ̀ iyanju lati maa yin Oluwa.**

EMAA yọ ni ti Oluwa, ẹ̀yin olododo: nitori ti ìyìn yẹ fun ẹni-ìdúró ṣinṣin. (Psm 32:11; 147:1.)

2. Ẹ maa fi dùùrù yin Oluwa: ẹ maa fi ohun-èlò olokun mẹwa kọrin si i. (Psm 96:3.)

3. Ẹ kọ orin titun si i: ẹ maa fi ọgbọọgbọ́n lù ohun-ọnà orin pẹlu ariwo. (Psm 96:1; 98:4.)

**A ni lati yin in nitori o jẹ Ọlọrun Ẹleda.**

4. Nitori ti ọ̀rọ̀ Oluwa tọ́: ati gbogbo iṣẹ́ rẹ̀ ni a nṣe ninú òtítọ́. (Psm 19:8; 119:90.)

5. O fẹ otitọ ati idajọ: ilẹ̀ ayé kun fun aanu Oluwa. (Psm 11:7; 119:64.)

6. Nipa ọ̀rọ̀ Oluwa ni a da awọn ọ̀run; ati gbogbo ogun wọn nipa èémí ẹnu rẹ̀. (Gen 11:3; Job 23:13.)

7. O gbá awọn omi òkun jọ bi ẹni pe nínú ìgò kan: o to ibu jọ ni ilé iṣura. (Psm 78:13.)

8. Ki gbogbo ayé ó bẹ̀rù Oluwa: ki gbogbo aráyé maa wà ninu ẹ̀rù rẹ̀. (O.D. 67:7; 96:9.)

9. Nitori ti o sọ̀rọ̀, o si ti ṣẹ; o paṣẹ, o si duro ṣinṣin. (Gen 1:3; Psm 148:5.)

**Ó jẹ́ Ọlọrun Olùpèsè.**

10. Oluwa mu ìmọ̀ awọn orilẹ-ede di asán: o mu arekereke awọn eniyan ṣákì. (Isa 8:10; 19:3.)

11. Ìmọ̀ Oluwa duro laelae, ìro inu rẹ lati irandiran. (Job 23:13; Owe 19:21; Psm 40:5.)

12. Ibukun ni fun orilẹ-ede naa, ti Ọlọrun rẹ̀ jẹ́ Oluwa; ati awọn eniyan naa ti ó ti yàn ṣe ìní rẹ̀. (Psm 144:13; Eks 19:5; Deut 7:6.)

13. Oluwa wò lati ọ̀run wá, ó rí gbogbo ọmọ eniyan. (Job 28:24; Psm 11:4.)

14. Lati ibùjokòó rẹ̀ o nwo gbogbo olugbe ayé.

15. O ṣe àyà wọn bakannáa; o kiyesi gbogbo iṣẹ́ wọn. (Jer 32:19.)

16. Ko si ọba kan ti a ti ọwọ́ ọ̀pọ̀ ogun gbà silẹ̀: ko si alagbara kan ti a fi agbara pupọ gba silẹ̀. (Psm 44:6.)

17. Ohun asán ni ẹṣin fun igbala: bẹẹ ni ki yoo fi agbara nla rẹ̀ gbàni silẹ. (Psm 20:7; Owe 21:31.)

18. Kiyesi i, ojú Oluwa nbẹ lara awọn ti o bẹ̀rù rẹ̀, lara awọn ti nreti ninu aanu rẹ̀. (Job 36:7; Psm 34:15; 147:11.)

19. Lati gba ọkàn wọn là lọ́wọ́ ikú, ati lati pa wọn mọ láàyè ni ìgbà ìyàn. (Psm 37:19.)

20. Ọkàn wa duro de Oluwa: oun ni iranlọwọ wa ati asà wa. (Psm 130:6.)

21. Nitori ti ọkàn wa yoo yọ̀ ni ti rẹ̀, nitori ti awa ti gbẹkẹle orukọ rẹ̀ mímọ́. (Sek 10:7; Jhn 16:22.)

22. Ki aanu rẹ, Oluwa, o wa lara wa, gẹgẹ bi awa ti nṣe ireti rẹ.

## ORIN 34.

**Ìyìn fun oore Ọlọrun.**

EMI o maa fi ibukun fun Oluwa nigba gbogbo: ìyìn rẹ̀ yoo maa wà lẹ́nu mi titi lae. (Ef 5:20; Psm 71:6.)

2. Ọkàn mi yoo maa ṣogo rẹ̀ ni ti Oluwa: awọn onirẹlẹ yoo gbọ, inu wọn yoo si maa dun. (Jer 9:24; Psm 119:74.)

3. Gbe Oluwa ga pẹlu mi, ki a si jùmọ̀ gbé orukọ rẹ̀ lékè. (Luk 1:46.)

4. Emi ṣe aferi Oluwa, o si gbóhùn mi; o si gba mi kuro nínú gbogbo ibẹru mi. (Matt 7:7; ẹsẹ 6,17,19.)

5. Wọ́n wò ó, imọlẹ si mọ wọ́n: ojú kò sì tì wọ́n. (Psm 36:9; 25:3.)

6. Ọkunrin olupọnju yìí kigbe pè, Oluwa si gbohun rẹ̀, o si gba a nínú gbogbo ipọnju rẹ̀: (ẹsẹ 4,17,19.)

**Ọ̀rọ̀ ìyànjú lati gbẹkẹle Ọlọrun ati lati maa wá a.**

7. Angẹli Oluwa yí awọn ti o bẹ̀rù rẹ̀ ká, o si gbà wọn. (Dan 6:22; 2 A.Ọba 6:17.)

8. Tọ́ ọ wò, ki o si ri pe, rere ni Oluwa: alábukun-fun ni ọkunrin naa ti o gbẹkẹle e. (1 Pet 2:3; Psm 2:12.)

9. Ẹ bẹru Oluwa, ẹ̀yin eniyan rẹ̀ mimọ: nitori ti kò sí aini fun awọn ti o bẹru rẹ̀, (Psm 23:1.)

10. Awọn ọmọ kinniun a maa ṣe aláìní, ebi a si maa pa wọn: ṣugbọn awọn ti nwa Oluwa, ki yoo ṣe alaini ohun ti o dára. (Psm 84:11.)

**Ìkìlọ̀ nipa ẹ̀ṣẹ̀ dida.**

11. Wá, ẹ̀yin ọmọ, fi eti si mi: emi o kọ yin ni ẹ̀rù Oluwa, (Psm 111:10.)

12. Ọkunrin wo ni o nfẹ ìyè, ti o si nfẹ ọjọ́ pupọ, ki o lè maa rí rere? (1 Pet 3:10.)

13. Pa ahọ́n rẹ mọ́ kuro nínú ibi, ati ètè rẹ kuro ni ẹ̀tàn sísọ. (1 Pet 2:22.)

14. Lọ kuro nínú ibi, ki o si maa ṣe rere; maa wá alaafia, ki o si lepa rẹ̀. (Psm 37:27; Heb 12:14.)

**A gba olododo là: eniyan buburu ṣègbé.**

15. Ojú Oluwa nbẹ lara awọn olododo, eti rẹ̀ si ṣí sí igbe wọn. (Job 36:7; Psm 33:18.)

16. Oju Oluwa kan si awọn ti nṣe buburu, lati ge iranti wọn kuro lori ilẹ̀. (Jer 44:11; Owe 10:7.)

17. Awọn olododo nke, Oluwa si gbọ, o si yọ wọn jade ninu ìṣẹ́ wọn gbogbo. (Psm 145:19; ẹsẹ 19.)

18. Oluwa nbẹ létí ọ̀dọ̀ awọn ti nṣe onirobinujẹ ọkàn; o si gba irú awọn ti nṣe onirora ọkàn là. (Psm 145:18; Isa 57:15.)

19. Ọpọlọpọ ni ipọnju olododo; ṣugbọn Oluwa gba a ninu wọn gbogbo. (Owe 24:16; ẹsẹ 4,6,17.)

20. Ó pa gbogbo egungun rẹ̀ mọ́; kò si ọkan ti o ṣẹ́ ninu wọn. (Jhn 19:36.)

21. Ibi ni yoo pa eniyan buburu; ati awọn ti o korira olododo yoo jẹ̀bi. (Psm 94:23.)

22. Oluwa ra ọkàn awọn iranṣẹ rẹ̀; ọ̀kan ninu awọn ti o gbẹkẹle e ki yoo jẹ̀bi. (1 A.Ọba 1:29; Psm 71:23.)

ORIN 35.

**Adura fun iranlọwọ: (1) ninu ìjìyà tabi ipọnju.**

OLUWA gbogun ti awọn ti o gbogun ti mi: fi ìjà fún awọn ti nba mi jà. (Psm 43:1.)

2. Di asà ati apata mu, ki o si dide fun iranlọwọ mi.

3. Fa ọkọ yọ pẹlu, ki o si dènà awọn ti nṣe inunibini si mi: wi fun ọkàn mi pe, "Emi ni ìgbàlà rẹ." (Psm 62:2.)

4. Ki wọn o daamu, ki a si ti awọn ti nwa ọkàn mi loju: ki a si mu wọn pada, ki a si daamu awọn ti ngbìrò ipalara mi. (Psm 79:2,3.)

5. Ki wọn o dabi ìyàngbò niwaju afẹ́fẹ́: ki angẹli Oluwa maa lé wọn, (Job 21:18; Psm 1:4; Isa 29:5.)

6. Ki ọ̀nà wọn o ṣokunkun ki o si maa yọ́; ki angẹli Oluwa si maa lepa wọn. (Psm 73:19; Jer 23:12.)

7. Nitori pé, ni ainidi ni wọn dẹ àwọ̀n wọn silẹ fun mi, wọn wa ihò silẹ fun ọkàn mi ni ainidi. (Psm 9:15.)

8. Ki iparun o wa si orí rẹ̀ ni òjijì; àwọ̀n rẹ̀ ti o dẹ, ki o mu oun tìkárarẹ̀: iparun naa ni ki o ṣubú sí. (1 Tess 5:3.)

9. Ọkàn mi yoo si maa yọ̀ ni ti Oluwa: yoo si maa yọ̀ ninu ìgbàlà rẹ̀. (Isa 61:10; Luk 1:47.)

10. Gbogbo egungun mi ni yoo wi pe, "Oluwa, tani o dabi iwọ, ti ngba talaka lọwọ awọn ti o lagbara ju u lọ, ani talaka ati alaini lọwọ eni ti nfi ṣe ikogun?" (Eks 15:11; Psm 18:17; 37:14.)

**(2) Lọwọ awọn abanijẹ.**

11. Awọn ẹlẹri èké dide; wọn nbi mi ni ohun ti emi kò mọ̀. (Psm 27:12.)

12. Wọn fi buburu san ore fun mi, lati sọ ọkàn mi di òfo. (Jhn 10:32.)

13. Ṣugbọn bi o ṣe temi ni, nigba ti ara wọn kò dá, aṣọ àwẹ̀ ni aṣọ mi: mo fi àwẹ̀ rẹ ọkàn mi silẹ; adura mi si pada si mi ní àyà. (Job 30:25; Psm 69:10.)

14. Emi ṣe ara mi bi ẹni pe ọ̀rẹ́ tabi arakunrin mi tilẹ̀ ni: emi fi ibanujẹ tẹriba, bi ẹni ti nṣọ̀fọ̀ ìyá rẹ̀.

15. Ṣugbọn ninu ipọnju mi wọn yọ̀, wọn si ko ara wọn jọ: awọn eniyankeniyan kó ara wọn jọ si mi, emi kò si mọ̀; wọn fà mí ya, wọn kò si dákẹ́. (Job 30:1,8.)

16. Pẹlu awọn agabagebe ti nṣe ẹlẹ́yà ni àpèjẹ, wọn npa ehín wọn si mi. (E.Jer. 2:16.)

17. Oluwa iwọ o ti maa wò pẹ́ tó? Yọ ọkàn mi kuro ninu iparun wọn, ẹmí mi kannaa lọwọ awọn kinniun. (Hab 1:13; Psm 22:20.)

18. Emi o ṣọpẹ́ fun ọ ninu ajọ nlá: emi o maa yin ọ ni àwùjọ ọpọ eniyan. (Psm 22:22,25.)

**(3) Lọwọ awọn akórìra ẹni.**

19. Máṣe jẹ́ ki awọn ti nṣe ọ̀tá mi o yọ̀ mi láìtọ́; bẹẹ ni ki o má si ṣe jẹ ki awọn ti o korira mi ni ainidi o maa ṣẹ́jú si mi. (Psm 13:4; 38:19; Owe 6:13; Psm 69:4; Jhn 15:25.)

20. Nitori ti wọn ko sọrọ alaafia: ṣugbọn wọn humọ̀ ọ̀ràn ẹ̀tàn si awọn eniyan jẹ́jẹ́ ilẹ̀ naa.

21. Nitootọ, wọn ya ẹnu wọn silẹ si mi, wọn wi pe, "A! aa! ojú wa ti ri i!" (Psm 22:13; 40:15.)

22. Eyi ni iwọ ti rí, Oluwa: máṣe dákẹ́: Oluwa máṣe jìnnà si mi. (Eks 3:7; Psm 28:1; 10:1.)

23. Rú ara rẹ soke, ki o si jí si idajọ mi, ati si ọ̀ràn mi, Ọlọrun mi ati Oluwa mi. (Psm 44:23.)

24. Ṣe idajọ mi, Oluwa Ọlọrun mi, gẹgẹ bi ododo rẹ, ki o má si ṣe jẹ ki wọn o yọ̀ mi. (Psm 9:4; ẹsẹ 19.)

25. Máṣe jẹ ki wọn o wi ninu ọkàn wọn pé, "A! bẹẹ ni awa nfẹ!" máṣe jẹ ki wọn o wi pe, "Awa ti gbe e mì." (E.Jer. 2:16.)

26. Ki ojú o ti wọn, ki wọn o si daamu pọ̀, awọn ti nyọ si ifarapa mi: ki a fi ìtìjú ati abùkù wọ wọn ni aṣọ, awọn ti ngberaga si mi. (Psm 40:14; 38:16.)

27. Jẹ ki wọn o maa hó fun ayọ̀, ki wọn si maa ṣe inu-didun awọn ti nṣe

oju-rere si ododo mi: jẹ ki wọn o maa wi titi pe, "Oluwa ni ki a maa gbega, ti o ni inú-dídùn si alaafia iranṣẹ rẹ̀. (Psm 32:11; 9:4; 40:16; 147:11.)

28. Ahọ́n mi yoo si maa sọ̀rọ̀ ododo rẹ̀, ati ti ìyìn rẹ̀ ni gbogbo ọjọ́. (Psm 51:14.)

## ORIN 36.

**Ìwà ẹ̀ṣẹ̀ eniyan buburu.**

EṢẸ̀ nsọ̀rọ̀ si eniyan buburu jínlẹ̀ ninu ọkàn rẹ̀. Ẹrù Ọlọrun kò sí niwaju rẹ̀. (Rom 3:18.)

2. Nitori ti o npọ́n ara rẹ̀ ni oju ara rẹ̀, títí a o fi ri ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ lati korira.

3. Ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ̀ ni ẹ̀ṣẹ̀ ati ẹ̀tàn: o ti fi ọgbọ́n ati iṣẹ́ rere silẹ. (Jer 4:22.)

4. O ngbiro ìwà-ìkà lori ẹní rẹ̀: o gba ọ̀nà ti ko dára; oun kò korira ibi. (Owe 4:16; Mika 2:1; Isa 65:2.)

**Ore ati Aanu Ọlọrun.**

5. Oluwa, aanu rẹ de ọ̀run; òtítọ́ rẹ̀ de ikuukuu awọsanma.

6. Ododo rẹ dabi awọn òkè Ọlọrun; idajọ rẹ dabi ibu nla: Oluwa, iwọ pa eniyan ati ẹranko mọ́. (Job 11:8; Psm 77:19; Rom 11:33.)

7. Ọlọrun, iṣeun-ifẹ rẹ ti dara tó! nitori naa ni awọn ọmọ eniyan yoo maa gbẹke wọn le abẹ́ òjìji íyẹ́-apá rẹ. (Rut 2:12.)

8. Adun ilé rẹ yoo tẹ wọn lọ́rùn gidigidi; iwọ o si mu wọn mu ninu odò inu-dídùn rẹ. (Psm 65:4; Job 20:17; Ifh 22:1.)

9. Nitori pé pẹlu rẹ ni orisun ìyè wa; ninu imọlẹ rẹ ni awa o maa ri imọlẹ. (Jer 2:13; 1 Pet 2:9.)

10. Mu iṣeun ifẹ rẹ pẹ si awọn ti o mọ̀ ọ; ati ododo rẹ fun awọn aláyà diduro.

11. Máṣe jẹ ki ẹsẹ̀ agberaga o wá si ori mi, ki o ma si ṣe jẹ ki ọwọ́ eniyan buburu ṣi mi ni ipò.

12. Nibẹ ni awọn oniṣẹ-ẹ̀ṣẹ̀ gbe ṣubú: a rẹ̀ wọn silẹ, wọn ki yoo sì lè dide. (Psm 140:10.)

## ORIN 37.

**Olododo yoo ṣe rere: eniyan buburu ni a o gé lulẹ̀.**

MÁṢE kanra nitori awọn oluṣebuburu, ki iwọ o máṣe ṣe ìlara nitori awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ̀. (Psm 73:3; Owe 23:17.)

2. Nitori ti a o ge wọn lulẹ̀ laipẹ bi koríko, wọn o si rọ bi eweko tútù. (Psm 90:5,6.)

3. Gbẹkẹle Oluwa, ki o si maa ṣe rere; maa gbe ilẹ naa, ki o si maa hùwà otitọ. (Psm 62:8; Deut 30:20; Isa 40:11.)

4. Ṣe inu-didun si Oluwa pẹlu, oun o si fi ìfẹ́ inu rẹ fun ọ. (Isa 58:14.)

5. Fi ọ̀nà rẹ lé Oluwa lọwọ; gbẹkẹle e pẹlu; oun o si ṣe e. (Psm 55:22; Owe 16:3; 1 Pet 5:7.)

6. Yoo si mu ododo rẹ jade bi imọlẹ, ati idajọ rẹ̀ bi ọ̀sángangan. (Job 11:17; Mika 7:9.)

7. Iwọ sinmi ninu Oluwa, ki o si fi suuru duro dè é; máṣe kanra nitori ẹni ti o nri rere ni ọ̀nà rẹ̀, nitori ọkunrin naa ti o nmu èrò buburu ṣẹ!

8. Dakẹ inu-bibi, ki o si kọ ìkannú sílẹ̀: máṣe kanra, ki o má baa ṣe buburu pẹlu. (Psm 73:3; Ef 4:26.)

9. Nitori ti a o ge awọn oluṣe buburu kuro: ṣugbọn awọn ti o duro de Oluwa ni yoo jogun ayé. (Isa 60:21.)

10. Nitori pe nigba diẹ, awọn eniyan buburu ki yoo si: nitootọ iwọ o fi ara balẹ wo ipò rẹ̀, ki yoo sì sì. (Job 24:24; 7:10.)

11. Ṣugbọn awọn ọlọkan-tutu ni yoo jogun ayé; wọn o si maa ṣe inu didun ninu ọpọlọpọ alaafia. (Matt 5:5.)

**Eniyan buburu ati eniyan rere.**

12. Eniyan buburu di rikiṣi si olootọ, o si pa ehin rẹ̀ keke si i lara. (Psm 35:16.)

13. Oluwa yoo rẹrin rẹ̀; nitori ti o ri pe ọjọ́ rẹ̀ nbọ̀. (Psm 2:4; 1 Sam 26:10.)

14. Awọn eniyan buburu ti fa idà yọ, wọn si ti fa ọrun wọn le, lati sọ ta-

laka ati alaini kalẹ̀, ati lati pa irú awọn ti nrin ni ọna títọ́. (Psm 11:2; 35:10.)

15. Idà wọn yoo wọ àyà wọn lọ, ọrun wọn yoo si ṣẹ́. (Psm 9:16.)

16. Ohun diẹ ti olododo ni san ju ọrọ̀ ọ̀pọ̀ eniyan buburu. (Owe 15:16.)

17. Nitori ti a o ṣẹ́ apá awọn eniyan buburu: ṣugbọn Oluwa di olododo mu. (Job 38:15; Psm 10:15.)

18. Oluwa mọ ọjọ́ ẹni iduro-ṣinṣin: ati ilẹ-ìní wọn yoo wa laelae. (Psm 1:6.)

19. Ojú ki yoo ti wọn ni ìgbà ibi: ati ni ọjọ ìyàn a o tẹ́ wọn lọ́rùn. (Job 5:20; Psm 33:19.)

20. Ṣugbọn awọn eniyan buburu yoo ṣègbé, awọn ọ̀tá Oluwa yoo dabi ẹwà oko-tútù: wọn o dopin; bi eefin ni wọn o parẹ́ kuro. (Psm 72:27; 102:3.)

21. Awọn eniyan buburu yá, wọn kò si pada san: ṣugbọn olododo a maa ṣaanu, a si maa fi funni. (Psm 112:5,9.)

22. Nitori ti awọn ẹni-ìbùkún rẹ̀ ni yoo jogun ayé; awọn ẹni-ègún rẹ̀ ni a o ge kuro. (Owe 3:33; Job 5:3.)

**Igbala ti o dájú ati ààbò ti awọn olododo.**

23. A ṣe ilana ẹsẹ̀ eniyan lati ọwọ́ Oluwa wá: o si ṣe inú dídùn si ọ̀nà rẹ̀. (1 Sam 2:9; Psm 147:11.)

24. Bi o tilẹ ṣubu, a ki yoo ta a nù kuro patapata; nitori ti Oluwa di ọwọ́ rẹ̀ mu. (Owe 24:16; Psm 147:6.)

25. Emi ti wà ni èwe, emi si dàgbà; emi koi ti i ri ki a kọ olódodo silẹ, tabi ki irú-ọmọ rẹ̀ o maa ṣagbe oúnjẹ. (Heb 13:5; Job 15:23.)

26. Alaanu ni oun nigba gbogbo, a maa yá ni: a si maa bùsi i fun irú-ọmọ rẹ̀. (ẹsẹ 21; Psm 147:13.)

27. Kuro ninu ibi ki o si maa ṣe rere; ki o si maa jókòó laelae. (Psm 34:14; ẹsẹ 18.)

28. Nitori ti Oluwa fẹ́ idajọ, ko si kọ awọn eniyan mimọ rẹ̀ silẹ; a si pa wọn mọ laelae: ṣugbọn irú-ọmọ awọn eniyan buburu ni a o ge kuro. (Psm 11:7; 21:10; Isa 14:20.)

29. Olododo ni yoo jogun ayé, yoo si maa gbe inu rẹ̀ laelae. (ẹsẹ 9,18.)

30. Ẹnu olododo ni i maa sọ̀rọ̀ ọgbọ́n, ahọ́n rẹ̀ a si maa sọ̀rọ̀ idajọ. (Matt 12:35.)

31. Ofin Ọlọrun rẹ̀ nbẹ ni àyà rẹ̀; ọ̀kan ninu irin rẹ̀ ki yoo yẹ̀. (Psm 40:8; Isa 51:7.)

32. Ẹni buburu nṣọ olódodo, o si nwá ọ̀nà lati pa a. (Psm 10:8.)

33. Oluwa ki yoo fi i lẹ e lọwọ, ki yoo si da a lẹbi, nigba ti a ba nṣe idajọ rẹ̀. (2 Pet 2:9; Psm 109:31.)

34. Duro de Oluwa, ki o si maa pa ọna rẹ̀ mọ́, yoo si gbe ọ leke lati jogun ayé: nigba ti a ba gé awọn eniyan buburu kuro, iwọ o ri i. (Psm 27:14; 52:5,6.)

35. Emi ti nri eniyan buburu, ẹni ìwà-ìkà, o si fi ara rẹ̀ gbilẹ̀ bí igi tútù nla. (Job 5:3.)

36. Ṣugbọn o kọja lọ, si kiyesi i, ko si mọ̀: lootọ emi wa a kiri, ṣugbọn a kò lè ri i. (Job 20:5.)

37. Maa kiyesi ẹni pípé, ki o si maa wo ẹni-ìdúró ṣinṣin: nitori alaafia ni òpin ọkunrin naa. (Isa 57:1,2.)

38. Ṣugbọn awọn alarekọja ni a o parun pọ̀; ìran awọn eniyan buburu ni a o gé kuro. (Psm 1:4; ẹsẹ 9,20,28.)

39. Ṣugbọn lati ọwọ́ Oluwa wa ni ìgbàlà awọn ọlọdodo; oun ni ààbò wọn ni ìgbà ipọnju. (Psm 3:8; 9:9.)

40. Oluwa yoo si ràn wọ́n lọwọ, yoo si gbà wọn, yoo si gba wọn lọwọ eniyan buburu, yoo si gbà wọn là, nitori ti wọn gbẹkẹle e. (Isa 31:5; 1 Kro 5:20.)

## ORIN 38.

**Ẹbẹ fun aanu.**

OLUWA, máṣe ba mi wi ninu ibinu rẹ: bẹẹ ni ki o máṣe nà mi ni gbígbóná ibinu-nlá rẹ. (Psm 6:1.)

2. Nitori ti ọfa rẹ kàn mọ́ mi ṣinṣin, ọwọ́ rẹ si ki mi mọ́lẹ̀. (Job 6:4; Psm 32:4.)

3. Kò si ibi yíyè ni ara mi nitori ibinu rẹ; bẹẹ ni kò si alaafia ni egungun mi nitori ẹ̀ṣẹ̀ mi. (Isa 1:6; Psm 6:2.)

4. Nitori ti ẹbi ẹ̀ṣẹ̀ mi kọja si orí mi, bi ẹrù wúwo, ó wúwo jù fun mi. (Esra 9:6.)

5. Ọgbẹ́ mi nrùn, o si díbàjẹ́ nitori ìwà-òmùgọ̀ mi. (Psm 69:5.)

6. Emi njòwèrè; orí mi tẹ̀ ba gidigidi; emi nṣọfọ rin kiri ni gbogbo ọjọ́. (Psm 35:14; 42:9.)

7. Nitori ti ẹ̀gbẹ́ mi kun fun ìgbóná-ti njoni; ko si si ibi yíyè lara mi. (Psm 102:3; ẹsẹ 3.)

8. Mo di gbígbẹ, ti a si ti tẹ̀ bàjẹ́, emi ti nkerora nitori aisinmi àyà mi. (Job 3:24; Psm 22:1.)

**Ifẹ fun igbala.**

9. Oluwa, gbogbo ifẹ mi nbẹ niwaju rẹ; ikerora mi ko si pamọ́ kuro lọdọ rẹ. (Psm 10:17; 6:6.)

10. Àyà mi nmi-hẹlẹ, agbara mi yẹ̀ mi silẹ̀: bi o ṣe ti ìmọ́lẹ̀ ojú mi ni, ko si lara mi. (Psm 31:10; 6:7.)

11. Awọn olufẹ ati awọn ọ̀rẹ́ mi duro lókèrè kuro ni ìyọnu mi, ati awọn ìbátan mi duro lokere réré. (Psm 31:11; Luk 23:49.)

12. Awọn pẹlu ti nwa ọkàn mi dẹkùn silẹ fun mi; ati awọn ti nwá ifarapa mi nsọ̀rọ̀ ohun buburu, wọn si ngbèrò ètàn ni gbogbo ọjọ́. (Psm 54:3; 140:5; 35:4,20.)

13. Ṣugbọn emi, bi adití, emi kò gbọ́; ati bi odi ti kò ya ẹnu rẹ̀. (Psm 39:2,9.)

14. Bẹẹ ni mo dabi ọkunrin ti kò gbọ́ràn, ati lẹnu ẹni ti iyàn kò sí.

**Igbẹkẹlẹ ninu Ọlọrun.**

15. Nitori, Oluwa, iwọ ni emi duro dè, iwọ o gbọ́, Oluwa Ọlọrun mi. (Psm 39:7; 17:6.)

16. Nitori ti mo wi pe, "Gbohun mi, ki wọn ma baa yọ̀ mí; nigba ti ẹsẹ̀ mi bá yọ́, wọn o maa gbé ara wọn ga sí mi." (Psm 13:4; 35:26.)

17. Emi ti mura lati ṣubú, ikaanu mi si nbẹ nigba-gbogbo niwaju mi. (Psm 13:2.)

18. Nitori ti emi o jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ mi; emi o kaanu nitori ẹ̀ṣẹ̀ mi. (Psm 32:5; 2 Kor 7:9.)

19. Ṣugbọn ara yá awọn ọ̀tá mi, ara wọn le; awọn ti o korira mi lainidi npọ si i. (Psm 18:17; 35:19.)

20. Awọn ti o si nfi buburu san rere ni ọ̀tá mi; nitori emi ntọpa ohun ti nṣe rere. (Psm 35:12; 1 Jhn 3:12.)

21. Oluwa, máṣe kọ̀ mi sílẹ̀; Ọlọrun mi, máṣe jìnna si mi. (Psm 35:22.)

22. Yara lati ran mi lọwọ, Oluwa ìgbàlà mi. (Psm 40:13,17; 27:1.)

## ORIN 39.

**Idakẹ ninu iṣoro.**

MO ni, "Emi o maa kiyesi ọ̀nà mi, ki emi ó má ṣe fi ahọ́n mi ṣẹ̀; emi o fi ìjanu kó ara mi lẹnu ni igba ti eniyan buburu ba nbẹ niwaju mi." (1 A.Ọba 2:4; Job 2:10; Jak 3:2.)

2. Mo fi idakẹ yadi, mo tilẹ̀ pa ẹnu mi mọ́ kuro ni ọ̀rọ̀ rere: ibanujẹ mi si ru soke. (Psm 38:13.)

3. Àyà mi gbóná ninu mi, nigba ti emi nronu, iná ràn: ni igba naa ni mo fi ahọ́n mi sọ̀rọ̀.

**Oluwa fi imọlẹ han Dafidi.**

4. "Oluwa, jẹ kí emi o mọ opin mi ati ìwọ̀n ọjọ́ mi, bi o ti ri; ki emi o lè mọ igba ti mo ni nihín. (Psm 90:12; 103:14.)

5. Kiyesi i, iwọ ti sọ ọjọ́ mi dabi ìbú àtẹ́lẹwọ́; ọjọ ori mi si dabi asán niwaju rẹ: nitootọ olukuluku eniyan ninu ipò rere rẹ̀ jásí asán patapata. (Psm 89:47; 144:4; 62:9.)

6. Nitootọ ni awoṛan asán ni eniyan gbogbo nrìn: nitootọ ni wọn nyọ ara wọn lẹnu lásán: ó nkó ọrọ̀ jọ, kò si mọ ẹni ti yoo kó wọn lọ. (1 Pet 1:24; Psm 127:2; Job 27:17; Luk 12:20.)

**Adura fun igbala.**

7. "Njẹ nisinsinyií, Oluwa kinni mo duro dè? Ireti mi nbẹ lọdọ rẹ. (Psm 38:15.)

8. Gbà mi ninu irekọja mi gbogbo ki o má si ṣe sọ mi di ẹni ègàn awọn eniyan buburu. (Psm 51:9; 44:13.)

9. Mo yadi, emi kò ya ẹnu mi; nitori pe iwọ ni o ṣe e. (ẹsẹ 2; Job 2:10.)

10. Mu ọwọ́ iná rẹ kuro lara mi: emi ṣègbé tan nipa ìjà ọwọ́ rẹ. (Job 9:34; Psm 32:4.)

11. Nigba ti iwọ ba fi ìbáwí kìlọ̀ fun eniyan nitori ẹ̀ṣẹ̀, iwọ a mu ẹwà rẹ parun bi kokoro aṣọ: nitootọ asán ni eniyan gbogbo. (2 Pet 2:16; Job 13:28; ẹsẹ 5.)

12. "Oluwa, gbọ́ adura mi, ki o si fi etí si ẹkún mi, ki o máṣe pa ẹnu rẹ mọ si omije mi: nitori àlejò ni emi lọ́dọ̀ rẹ, ati àtìpó, bi gbogbo awọn baba mi ti ri. (Psm 102:1; 56:8; Heb 11:13; 1 Pet 2:11.)

13. Dá mi sí, ki emi lè ni agbara, ki emi to lọ kuro nihinyìí, ati ki emi o tó ṣe alaisi. (Job 10:20; 14:10.)

## ORIN 40.

**Inudidun si ifẹ Oluwa.**

NI diduro emi duro de Oluwa; o si dẹtí si mi, o si gbóhùn ẹkún mi. (Psm 27:14; 34:15.)

2. O si mu mi goke jade wá pẹlu lati inu ihò iparun, lati inu erupẹ ẹrẹ̀, o si fi ẹsẹ̀ mi ka orí apata, o si fi ìṣísẹ̀ mi lélẹ̀. (Psm 69:2; 27:5.)

3. O si fi orin titun si mi lẹ́nu, ani orin ìyìn si Ọlọrun wa: ọpọ eniyan ni yoo ri i, ti yoo si bẹ̀rù, ti yoo si gbẹkẹle Oluwa. (Psm 33:3.)

4. Ibukun ni fun ọkunrin naa ti o fi Oluwa ṣe ìgbẹ́kẹ̀lé rẹ̀, ti kò sì ka onirera si, tabi irú awọn ti nya si ìhà èké. (Psm 84:12.)

5. Oluwa Ọlọrun mi ọpọlọpọ ni iṣẹ́ iyanu ti iwọ ti nṣe, ati ìrò inu rẹ sípa ti wa: a kò lè kà wọn fun ọ lẹ́sẹẹsẹ, bi emi o wí, ti emi o sọ̀rọ̀ wọn, wọn ju ohun kíkà lọ. (Psm 136:4; Isa 55:8; Psm 139:18.)

**Ìgbọ́ràn san ju ẹbọ.**

6. Ẹbọ ati ọrẹ iwọ kò fẹ́: etí mi ni iwọ ti ṣí: ọrẹ-ẹbọ sisun, ati ọrẹ-ẹbọ ẹ̀ṣẹ̀ oun ni iwọ kò bèèrè. (1 Sam 15:22.)

7. Ni igba naa ni mo wi pe, "Kiyesi i, emi dé: ninu ìwé-kíká ni a gbe kọwe mi pe.

8. Inu mi dun lati ṣe ifẹ rẹ, Ọlọrun mi, nitootọ, ofin rẹ nbẹ ni àyà mi." (Jhn 4:34; Rom 7:22; Psm 37:31.)

9. Emi ti waasu ododo ninu àwùjọ nla: kiyesi i, emi ko pa ètè mi mọ, Oluwa, iwọ mọ̀. (ẹsẹ 2; Job 2:10.)

10. Emi kò fi ododo rẹ sin ni àyà mi, emi o sọrọ otitọ ati ìgbàlà rẹ: emi kò si pa iṣeun-ifẹ rẹ ati otitọ rẹ mọ́ kuro lọdọ ijọ nla nì. (A.A. 20:20; Psm 89:1.)

**Adura Dafidi fun aanu ati ore-ọfẹ.**

11. Iwọ máṣe fa ìkẹ́ aanú rẹ sẹhin kuro lọ́dọ̀ mi, Oluwa; ki iṣeun ifẹ rẹ ati otitọ rẹ maa pa mi mọ ni igba gbogbo. (Psm 43:3.)

12. Nitori pe àìníye ibi ni o yi mi ká kiri: ẹ̀ṣẹ̀ mi di mọ mi, bẹẹ ni emi kò lè gbé ojú wo òkè, wọn ju irun orí mi lọ: nitori naa àyà mi npá mi. (Psm 116:3; 38:4; 69:4; 73:26.)

13. Ki o wu ọ, Oluwa, lati gbà mi: Oluwa, yara lati ràn mi lọwọ. (Psm 70:1.)

14. Ki ojú o tì wọn, ki wọn si dààmú pọ̀ awọn ti nwa ọkàn mi lati pa a run; ki a lé wọn pada sẹ́hìn, ki a si dojuti awọn ti nfẹ ibi mi. (Psm 35:4; 63:9.)

15. Ki wọn o di òfo fun ère ìtìjú wọn, awọn ti nwi fun mi pe, "A! a!" (Psm 70:3.)

16. Ki gbogbo awọn ti nwa ọ, ki o maa yọ̀, ki inu wọn si maa dùn sipa tìrẹ: ki gbogbo awọn ti o si fẹ ìgbàlà rẹ maa wi ni igba gbogbo pe, "Gbigbega ni Oluwa." (Psm 70:4; 35:27.)

17. Ṣugbọn talaka ati alaini ni emi; Oluwa si nṣe iranti mi; iwọ ni iranlọwọ mi ati olugbala mi: máṣe pẹ titi, Ọlọrun mi. (Psm 70:5.)

## ORIN 41.

**Ibukun ti o wa fun awọn alaanu.**

IBUKUN ni fun ẹni, ti nro ti awọn alaini, Oluwa yoo gba a ni igba ìpọ́njú. (Psm 82:3,4; Owe 14:21.)

2. Oluwa yoo pa a mọ, yoo si mu un wà láàyè; a o si bùkún fun un lori ilẹ̀: iwọ ki yoo si fi i le ìfẹ́ àwọn ọ̀tá rẹ̀ lọ́wọ́. (Psm 37:22,28; 27:12.)

3. Oluwa yoo gba a ni ìyànjú lori ẹni àrùn: ìwọ o maa pààrọ̀ ẹní rẹ̀ gbogbo ni idubulẹ àrùn rẹ̀. (Psm 6:6.)

**Ara kan awọn ọ̀rẹ́ èké.**

4. Emi wi pe, "Oluwa ṣaanu fun mi: mu ọkàn mi lara dá; nitori ti mọ ti ṣẹ̀ si ọ." (Psm 6:2; 51:4.)

5. Awọn ọ̀tá mi nsọ ibi si mi pe, "nígbàwo ni oun o kú, tí orukọ rẹ̀ yoo si run?" (Psm 38:12.)

6. Bi o ba si wá wò mi, oun a maa sọrọ ẹ̀tàn; àyà rẹ kó ẹ̀ṣẹ̀ jọ si ara rẹ̀; ni igba ti o ba jade lọ, a maa wi i. (Psm 12:2.)

7. Gbogbo awọn ti o korira mi jumọ nsọrọ kẹ̀lẹ́ si mi: emi ni wọn ngbimọ ibi si. (Psm 56:5.)

8. Pe, "Ohun buburu ni o dì mọ́ ọn ṣinṣin: ati ni ibi ti o dubulẹ si, ki yoo dide mọ." (Psm 71:10,11.)

9. Nitootọ, ọ̀rẹ́ mi tímọ́tímọ́ ẹni ti mo gbẹkẹle, ẹni ti njẹ ninu ounjẹ mi, o gbe gigisẹ rẹ̀ si mi. (Job 19:19; Psm 55:12; Jhn 13:18.)

10. Ṣugbọn iwọ, Oluwa, ṣaanu fun mi, ki o si gbe mi dide, ki emi lè san an fun wọn. (Psm 3:3.)

**Idálare nipa ìwàtítọ́.**

11. Nipa eyi ni mo mọ̀ pe iwọ ṣe oju-rere si mi, nitori ti awọn ọta mi kò yọ̀ mí. (Psm 147:11; 25:2.)

12. Bi o ṣe temi ni, iwọ dì mi mu ninu ìwàtítọ́ mi, iwọ si gbe mi kalẹ niwaju rẹ titi lae. (Psm 37:17; Job 36:7.)

**Orin ìyìn si Ọlọrun.**

13. Olubukun ni Oluwa, Ọlọrun Israẹli, lae ati laelae. Amín, ati Amin. (Psm 106:48.)

## IWE KEJÌ.

## ORIN 42.

**Ibanujẹ ati ìtùnú awọn ẹni iwa-bi-ọlọrun.**

BI agbọnrin ti maa nmi hẹlẹ si ipado omi, Ọlọrun, bẹẹ ni ọkàn mi nmi hẹlẹ si ọ. (Psm 119:31.)

2. Oungbẹ Ọlọrun ngbẹ ọkàn mi, ti Ọlọrun alaaye: nigbawo ni emi o wa, ti emi o si yọjú niwaju Ọlọrun. (Psm 63:1; Jer 10:10; Psm 43:4.)

3. Omijé mi ni ounjẹ mi lọsan ati loru, nigba ti wọn nwi fun mi ni ìgbà gbogbo pe, "Ọlọrun rẹ dà?" (Psm 80:5; 79:10.)

4. Ni igba ti mo bá ranti nkan wọnyìí, emi tú ọkan mi jade ninu mi: emi ti ba ọpọ ijọ eniyan lọ, emi ba wọn lọ si ile Ọlọrun, pẹlu ohùn ayọ̀ ati ìyìn, pẹlu ọ̀pọ̀ eniyan ti npa ọjọ mímọ́ mọ́. (Psm 62:8; Isa 30:29; Psm 100:4.)

5. Eeṣe ti orí rẹ fi tẹ̀ba, iwọ ọkàn mi? Eeṣe ti ara rẹ kò fi lélẹ̀ ninu mi? Iwọ ṣe ìrètí ni ti Ọlọrun: nitori emi o saa maa yìn ín síbẹ̀ fun iranlọwọ ojú rẹ̀. (Psm 38:6; 77:3; E.Jer. 3:24; Psm 44:3.)

**Ìtùnú ati ìrètí awọn ẹni ìwà-bi-ọlọrun.**

6. Ọlọrun mi, orí ọkàn mi tẹ̀ ba ninu mi: nitori naa ni emi o ṣe ranti rẹ lati ilẹ̀ Jordani wá, ati lati Hermoni, lati òkè Misari wá.

7. Ibú omi npe ibú omi nipa híhó ṣíṣàn-omi rẹ: gbogbo rírú omi ati bíbì omi rẹ bò mi mọ́lẹ̀. (Psm 88:7; Jona 2:3.)

8. Ṣugbọn Oluwa yoo pàṣẹ iṣegun-ifẹ nigba ọ̀sán, ati ni òru orin rẹ̀ yoo wa pẹlu mi, ati adura mi si Ọlọrun ẹmi mi. (Psm 57:3; Job 35:10; Psm 63:6; 149:5.)

9. Emi o wi fun Ọlọrun, apata mi pe, "Eeṣe ti iwọ fi gbagbe mi? Eeṣe ti emi fi nrin ni ìgbààwẹ̀ nitori inilara ọ̀tá?" (Psm 38:6.)

10. Bi ẹni pe idà ninu egungun mi ni ẹ̀gàn ti awọn ọ̀tá mi ngan mi; nigba ti

wọn nwi fun mi lojoojumọ pe, "Ọlọrun rẹ dà?" (ẹsẹ 3.)

11. Eeṣe ti ori rẹ fi tẹba, iwọ ọkan mi? Eeṣe ti ara rẹ kò fi lélẹ̀ ninu mi? Iwọ ṣe ìrètí ni ti Ọlọrun; nitori emi o saa maa yin in sibẹ, ẹni ti nṣe iranlọwọ mi ati Ọlọrun mi. (ẹsẹ 5.)

ORIN 43.

**Ẹbẹ̀ fun idalare.**

SE idajọ mi, Ọlọrun, ki o si gba ọ̀ràn mi rò si alailaanu orilẹ-ede: gba mi lọwọ ẹlẹtan ati ọkunrin alaiṣootọ nì. (Psm 26:1; 1 Sam 24:15; Psm 5:6.)

2. Nitori iwọ ni Ọlọrun agbara mi: eeṣe ti iwọ fi ṣá mi tì? Eeṣe ti emi fi nrin ni ìgbàwẹ̀ nitori inilara ọta ni? (Psm 18:1; 44:9; 42:9.)

3. Ran imọlẹ rẹ ati otitọ rẹ jade, ki wọn o maa ṣe amọ̀nà mi: ki wọn mu mi gun òkè mímọ́ rẹ, ati sinu awon àgọ́ rẹ. (Psm 36:9; 42:4; 84:1.)

4. Ni igba naa ni emi o lọ si ibi pẹpẹ Ọlọrun, sọdọ Ọlọrun ayọ̀ nla mi: nitootọ, lara dùùrù ni emi o maa yin ọ, Ọlọrun, Ọlọrun mi. (Psm 26:6; 33:2.)

5. Eeṣe ti ori rẹ fi tẹba, iwọ ọkan mi? Eeṣe ti ara rẹ kò fi lelẹ ninu mi? Iwọ ṣe ìrètí ni ti Ọlọrun: nitori ti emi o saa maa yìn ín sibẹ, ẹni ti nṣe iranlọwọ ojú mi, ati Ọlọrun mi. (Psm 42:5,11.)

ORIN 44.

**Adura fun idande.**

OLỌRUN, awa ti fi eti wa gbọ́, awọn baba wa si ti sọ fun wa niti iṣẹ nla ti iwọ ṣe lọjọ wọn, ni ìgbà ọjọ́ pípẹ́. (Eks 12:26; Psm 78:3,12.)

2. Bi iwọ ti fi ọwọ́ rẹ le awọn keferi jade, ṣugbọn iwọ si gbin wọn: bi iwọ ti fooró awọn eniyan naa, awọn ni iwọ si mu gbilẹ̀. (Eks 15:17; Psm 78:55; 80:8.)

3. Nitori ti wọn kò gba ilẹ̀ naa nípa idà ara wọn, bẹẹ ni ki i ṣe apá wọn ni ó gbà wọ́n; bikoṣe ọwọ́ ọ̀tún rẹ ati apá rẹ, ati imọlẹ ojú rẹ, nitori ti iwọ ni ifẹ rere si wọn. (Jos 24:12; Psm 77:15; Deut 4:37; 7:7,8.)

4. Iwọ ni Ọba mi, Ọlọrun: paṣẹ igbala fun Jakọbu. (Psm 74:12; 79:9.)

5. Nipasẹ rẹ ni awa o bi awọn ọ̀tá wa ṣubú: nipasẹ̀ orukọ rẹ ni awa o tẹ awọn ti o dide si wa mọ́lẹ̀. (Dan 8:4; Psm 108:13.)

6. Nitori ti emi ki yoo gbẹkẹle ọrun mi, bẹẹ ni idà mi ki yoo gbà mi. (Psm 33:16.)

7. Ṣugbọn iwọ ni o ti gbà wa lọwọ awọn ọta wa, iwọ si ti dojuti awọn ti o korira wa. (Psm 136:24; 53:5.)

8. Ninu Ọlọrun ni awa nkọrin ìyìn lọjọ gbogbo, awa si nyin orúkọ rẹ̀ laelae. (Psm 34:2; 30:12.)

**Ẹdùn ọkàn awọn eniyan.**

9. Ṣugbọn iwọ ti ṣá tì, iwọ si ti dojutì wa: iwọ kò si ba ogun wa jade lọ. (Psm 60:1,10; 74:1.)

10. Iwọ mu wa pẹ̀hìndà fun ọ̀tá wa: ati awọn ti o korira wa nṣe ikogun fun ara wọn. (Lef 26:17; Jos 7:8; Psm 89:41.)

11. Iwọ ti fi wa fun jíjẹ bi ẹran àgùtàn; iwọ si ti tú wa ká ninu awọn keferi. (ẹsẹ 22; Deut 4:27; 28:64; Psm 106:27.)

12. Iwọ ti ta awọn eniyan rẹ lásán, iwọ kò si fi iye-owó wọn sọ ọrọ̀ rẹ di pupọ. (Isa 52:3,4; Jer 15:13.)

13. Iwọ sọ wa di ẹ̀gàn si awọn aladugbo wa, ẹlẹ́yà ati iyọṣùtì-sí, si awọn ti o yi wa ka. (Psm 79:4; 80:6.)

14. Iwọ sọ wa di ẹni-ìfiṣọ̀rọ̀sọ laarin orilẹ-èdè, ati ìmì orí sí laarin awọn eniyan. (Jer 24:9; Psm 109:25.)

15. Idaamu mi nbẹ niwaju mi nigba gbogbo, itiju mi si bò mi mọlẹ.

16. Nitori ohùn ẹni ti ngàni, ti o si nsọ̀rọ̀ buburu, nisojú ọ̀tá ati olugbẹsan. (Psm 74:10; 8:2.)

**Ẹbẹ̀ si Ọlọrun fun igbala.**

17. Gbogbo wọnyí ni o de si wa; ṣugbọn awa kò gbagbe rẹ, bẹẹ ni awa

kò ṣe èké ni majẹmu rẹ. (Dan 9:13; Psm 78:7,57.)

18. Àyà wa kò pada sẹhin, bẹẹ ni ìrìn wa kò yà kuro ni ipa tirẹ (Psm 78:57; Job 23:11.)

19. Bi iwọ tilẹ ti fọ́ wa bàjẹ́ ni ibi awọn akátá, ti iwọ si fi ojiji ikú bò wa mọlẹ. (Psm 51:8; Job 3:5.)

20. Bi o ba ṣe pe awa gbagbe orukọ Ọlọrun wa, tabi bi awa ba na ọwọ́ wa si ọlọrun àjèjì. (Psm 78:11; 68:31; 81:9.)

21. Njẹ Ọlọrun ki yoo ri ìdí rẹ̀? Nitori o mọ ohun ìkọ̀kọ̀ àyà. (Psm 139:1,2; Jer 17:10.)

22. Nitootọ, nitori rẹ ni a ṣe npa wa kú ni gbogbo ọjọ́; a nkà wá si bi àgùtàn fun pípa. (Rom 8:36; Isa 53:7.)

23. Ji! eeṣe ti iwọ nsun, Oluwà? Dide, máṣe ṣá wa tì kuro laelae. (Psm 7:6; 78:65; 77:7.)

24. Eeṣe ti iwọ fi pa ojú rẹ mọ, ti iwọ si fi gbagbe ipọnju wa ati inira wa? (Job 13:24; Psm 42:9.)

25. Nitori ti a tẹri ọkàn wa ba sinu ekuru: inu wa di mọ erupẹ ilẹ̀. (Psm 11:25.)

26. Dide fun iranlọwọ wa, ki o si rà wá pada nitori aanu rẹ. (Psm 35:2; 25:22.)

## ORIN 45.

**Ọba ati ètò ijọba rẹ̀.**

AYÀ mi kun akunwọsilẹ fun ọ̀ràn rere: emi nsọ ohun ti mo ti ṣe, fun ọba: ahọ́n mi si dabi kálàmù ayára kọwe. (Esra 7:6.)

2. Iwọ yanju jù awọn ọmọ eniyan lọ: a da oore-ọ̀fẹ́ si ọ ni ètè: nitori naa ni Ọlọrun ṣe bukun fun ọ laelae. (Luk 4:22.)

3. Sán idà rẹ mọ idi rẹ, Alagbara julọ, ninu ogo rẹ ati ọlá-nla rẹ. (Isa 9:6.)

4. Ati ninu ọlá-nla rẹ maa gẹṣin lọ ni alaafia, nitori otitọ ati iwa-tútù ati ododo; ọwọ́ ọ̀tún rẹ yoo si kọ́ ọ lóhun ẹ̀rù. (Ifh 6:2.)

5. Ọfà rẹ mu, ni àyà awọn ọ̀tá ọba; awọn eniyan nṣubu nisalẹ ẹsẹ̀ rẹ.

6. Ọlọrun, lae ati laelae ni ìtẹ́ rẹ: ọpa-alade ijọba rẹ ọ̀pá-alade otitọ ni. (Psm 93:2; Heb 1:8,9; Psm 98:9.)

7. Iwọ fẹ ododo, iwọ korira ìwà-bú-burú: nitori naa ni Ọlọrun, Ọlọrun rẹ, ṣe fi àmì òróró ayọ̀ yan ọ ṣolori awọn ẹlẹgbẹ rẹ. (Psm 33:5; Isa 61:1; Psm 79:4.)

8. Gbogbo aṣọ rẹ ni o nrun turari, ati aloe, ati kassíà, lati inu aafin ehín-erin, ni ohun-ọnà orin olókùn nmu ọ yọ̀. (O.Sol. 1:3.)

9. Awọn ọmọbinrin awọn alade wa ninu awọn ayanfẹ rẹ: ni ọwọ́ ọ̀tún rẹ ni ayaba naa gbe duro ninu wúrà Ofiri. (O.Sol. 6:8; 1 A.Ọba 2:19.)

**Iyawo ati ètò igbeyawo.**

10. Dẹti silẹ, ọmọbinrin, si ronú, si dẹ eti rẹ silẹ! gbagbe awọn eniyan rẹ, ati ile baba rẹ! (Deut 21:13.)

11. Bẹẹ ni Ọba yoo fẹ ẹwà rẹ gidigi-di: nitori oun ni Oluwa rẹ; ki iwọ si maa sin in. (Psm 95:6; Isa 54:5.)

12. Ọmọbinrin Tire pẹlu ọrẹ; ati awọn ọlọ́rọ̀ ninu awọn eniyan yoo maa bẹ̀bẹ̀ ojú-rere rẹ. (Psm 22:29.)

13. Ti ògo, ogo ni ọmọbinrin ọba naa ninu ilé: iṣẹ wura ọna-abẹ́rẹ́ ni aṣọ rẹ̀. (Isa 61:10.)

14. Ninu aṣọ iṣẹ́ ọnà-abẹrẹ ni a o mu un tọ ọba wá: awọn wundia, ẹgbẹ rẹ̀ ti ntọ ọ lẹhin ni a o mu tọ ọ wa. (O.Sol. 1:4; ẹsẹ 9.)

15. Pẹlu inu didun ati pẹlu ayọ̀ ni a o fi mu wọn wá: wọn o si wọ aafin ọba lọ.

**Ọ̀rọ̀ Asọpari.**

16. Ni ipò awọn baba rẹ ni awọn ọmọ rẹ yoo wà, ẹni ti iwọ o maa fi jẹ oyè lori ilẹ̀ gbogbo. (1 Pet 2:9; Ifh 1:6; 20:6.)

17. Emi o maa ṣe orukọ rẹ ni iranti ni ìran gbogbo: nitori naa ni awọn eniyan yoo ṣe maa yìn ọ lae ati laelae. (Mal 1:11; Psm 138:4.)

ORIN 46.

**Ọlọrun ni Ààbò wa ati agbara wa.**

OLỌRUN ni ààbò wa ati agbara, lọ́wọ́lọ́wọ́ ìránlọ́wọ́ ni ìgbà ipọnju. (Psm 14:6; Deut 4:7; Psm 9:9.)
2. Nitori naa àwa ki yoo bẹ̀rù, bi a tilẹ ṣi ayé ni ìdí, ti a si ṣi awọn òkè nla nípò lọ si inu òkun: (Psm 23:4; 82:5; 18:7.)
3. Bi omi rẹ̀ tilẹ nhó ti o si nrú, bi awọn òkè nla tilẹ nmi nipa ọwọ́ bíbì rẹ̀. (Psm 93:3,4.)

**Ọlọrun ni Agbara wa.**

4. Odò nla kan wà, ṣíṣàn eyi ti yoo mu inu ilu Ọlọrun dùn, ibi mímọ́ agọ ti Ọga-ogo. (Isa 8:7; Psm 48:1,8; Isa 60:14.)
5. Ọlọrun nbẹ laarin rẹ̀; a ki yoo ṣi i ni ìdí: Ọlọrun yoo ran an lọwọ ni kutukutu owurọ. (Isa 12:6; Psm 37:40.)
6. Awọn orilẹ-ede nbinu, awọn ilẹ̀ọba ṣidi: o fọhun rẹ̀, ayé yọ́. (Psm 2:1; 68:33; Mika 1:4.)
7. Oluwa awọn ọmọ-ogun wà pẹlu wa; Ọlọrun Jakọbu ni ààbò wa. (2 Kro 13:12; Psm 9:9.)

**Ọlọrun ni Iṣẹgun wa.**

8. Ẹ wá wo awọn iṣẹ́ Oluwa, irú ahoro ti o ṣe ni ayé. (Psm 66:5; Isa 61:4.)
9. Ó mu ọ̀tẹ̀ tán dé opin ayé; o ṣẹ́ ọrun, o si ge ọ̀kọ̀ si meji; o si fi kẹ̀kẹ́ ogun jóná. (Isa 2:4; Psm 76:3; Esk 39:9.)
10. Ẹ duro jẹ, ki ẹ si mọ̀ pe emi ni Ọlọrun, a o gbe mi ga ninu awọn keferi, a o gbé mi ga ni ayé. (Psm 100:3; Isa 2:11,17.)
11. Oluwa awọn ọmọ-ogun wà pẹlu wa; Ọlọrun Jakọbu ni ààbò wa.

ORIN 47.

**Awọn Orilẹ-ede ni a tẹrí wọn ba.**

EYIN eniyan gbogbo, ẹ pàtẹ́wọ́; ẹ fi ohùn ayọ̀ hó ìhó iṣẹgun si Ọlọrun. (Psm 98:8; Isa 55:12; Psm 106:47.)
2. Nitori Oluwa Ọga-ogo múná; oun ni Ọba nla lori ilẹ-ayé gbogbo. (Deut 7:21.)
3. Oun ni yoo tẹrí awọn eniyan ba labẹ wa, ati awọn orilẹ-ede ni àtẹ́lẹsẹ̀ wa. (Psm 18:47.)
4. Oun ni yoo yan ilẹ-ìní wa fun wa, ọlá Jakọbu, ẹni ti o fẹ. (1 Pet 1:4.)

**Ọlọrun jọba lori gbogbo ayé.**

5. Ọlọrun goke lọ pẹlu ariwo, Oluwa pẹlu iró ipè. (Psm 68:33; 98:6.)
6. Ẹ kọrin ìyìn si Ọlọrun, ẹ kọrin ìyìn: ẹ kọrin ìyìn si Ọba wa, ẹ kọrin ìyìn. (Psm 68:4; 89:18.)
7. Nitori Ọlọrun ni Ọba gbogbo ayé: ẹ fi òye kọrin ìyìn. (1 Kor 14:15.)
8. Ọlọrun jọba awọn keferi: Ọlọrun jókòó lori ìtẹ́ iwa-mimọ rẹ̀. (1 Kro 16:31.)
9. Awọn alade awọn eniyan kó ara wọn jọ, ani awọn eniyan Ọlọrun Abrahamu: nitori asà ayé ti Ọlọrun ni: oun ni a gbé lékè jọjọ. (Psm 72:11; Rom 4:11,12; Psm 89:18; 87:9.)

ORIN 48.

**Sioni ìlú Ọlọrun wa.**

ENI-NLA ni Oluwa, ti a o yin pupọpupọ, ni ilu Ọlọrun wa, ni òkè iwa-mimọ rẹ̀. (Psm 96:4; Sek 8:3.)
2. Didara ni ipò giga, ayọ̀ gbogbo ayé ni òkè Sioni, ni ìhà ariwa, ilu Ọba nla. (Psm 50:2; E.Jer. 2:15; Matt 5:35.)
3. A mọ̀ Ọlọrun ni ààbò to dájú ninu aafin rẹ̀. (Psm 46:7.)

**Ìfẹṣẹ̀múlẹ̀ Sioni.**

4. Sa wo o, awọn ọba péjọ pọ̀, wọn jumọ nkọja lọ. (2 Sam 10:6–19.)
5. Wọn ri i, bẹẹ ni ẹnu ya wọn; a yọ wọn lẹ́nu, wọn yára lọ. (Eks 15:15.)
6. Ẹrù ba wọn níbẹ̀, ati irora bi obinrin ti nrọbi.
7. Iwọ fi ẹfuufu ila-oòrùn fọ́ ọkọ̀-ojuomi Tarsisi. (Jer 18:17.)
8. Bi awa ti gbọ́, bẹẹ ni awa ri ni ilu

Oluwa awọn ọmọ-ogun, ni ilu Ọlọrun wa: Ọlọrun yoo gbe e kalẹ laelae. (Psm 87:5.)

**Sioni nfi iyin fun Oluwa.**

9. Awa ti nro ti iṣeun-ifẹ rẹ, Ọlọrun, laarin tẹmpili rẹ. (Psm 26:3.)

10. Ọlọrun, gẹgẹ bi orukọ rẹ, bẹẹ ni iyin rẹ de opin ayé: ọwọ ọtun rẹ kun fun ododo. (Jos 7:9; Isa 41:10.)

11. Ki òkè Sioni yọ, ki inu awọn ọmọbinrin Juda si dùn, nitori idajọ rẹ. (Psm 97:8.)

12. Rin kiri Sioni, ki o si yi i ka: kà ile-iṣọ rẹ.

13. Kiyesi odi rẹ, kiyesi awọn aafin rẹ; ki ẹyin le maa wi fun iran ti o tẹlẹ yin. (Psm 122:7; 78:5–7.)

14. Nitori Ọlọrun yii Ọlọrun wa ni lae, ati laelae; oun ni yoo maa ṣe amọna wa titi ikú. (Psm 23:4.)

ORIN 49.

**Iwaasu lori iwà – òmùgọ̀ ti o wa ninu gbigbẹkẹlé ọrọ̀.**

EGBỌ eyi, gbogbo eniyan; ẹ fi etí si i, gbogbo ẹyin aráyé. (Psm 78:1; 33:8.)

2. Ati awọn ọmọ-ẹhin ati awọn ẹni-ọlọlá, awọn ọlọ́rọ̀ ati awọn tálákà pẹlu.

3. Ẹnu mi yoo sọrọ̀ ọgbọ́n, ati iṣàrò àyà mi yoo jẹ òye. (Psm 37:30; 119:130.)

4. Emi o dẹ etí mi silẹ̀ si òwe: emi o ṣi ọrọ-àlọ́ mi silẹ loju okùn dùùrù. (Psm 78:2; Num 12:8.)

**Ọrọ̀ kò lè gbani.**

5. Eeṣe ti emi o fi bẹ̀rù ni ọjọ ibi, ni ìgbà ti ẹ̀ṣẹ̀ awọn ajinilẹsẹ mi yi mi ka. (Psm 23:4.)

6. Awọn ti o gbẹkẹle ọrọ̀ wọn, ti wọn si nṣe ileri ni ọpọlọpọ ọrọ̀ wọn. (Job. 31:24.)

7. Kò si ẹnikan, bi o ti wù ki o ṣe, ti o lè ra arakunrin rẹ, bẹẹ ni kò lè san owó-ìràpadà fun Ọlọrun nitori rẹ. (Matt. 25:8,9; Job 36:18.)

8. Nitori ìràpadà ọkàn wọn iyebíye ni, o si ti dẹkun laelae. (Matt. 16:26.)

9. Ni ti pe ki o le maa wa laelae, ki o má ṣe ri isa-òkú. (Psm 22:29; 89:48.)

10. Nitori o nri pe awọn ọlọgbọn nku, bẹẹ ni aṣiwere ati ẹranko eniyan nṣègbé, wọn si nfi ọrọ̀ wọn silẹ fun ẹlomiran. (Onws 2:16,18.)

11. Irò inú wọn ni, ki ilé wọn o pẹ titi lae, ati ibùjokòó wọn lati irandiran; wọn sọ ilẹ̀ wọn nipa orukọ ara wọn. (Psm 64:6; 10:6; Deut 3:14.)

12. Ṣugbọn eniyan ti o wà ninu ọlá ko duro pẹ́: o dabi ẹranko ti o ṣègbé. (ẹsẹ 20.)

**Igbẹhin awọn ti o gbẹkẹlẹ ọrọ̀.**

13. Eyi ni ipa-ọna awọn ti o ni igbẹkẹle wèrè; ati ti awọn ti o mbọ lẹhin wọn ti ọrọ̀ wọn si tọ́ loju wọn. (Luk 12:20.)

14. Bi agutan ni a ntẹ́ wọn si ìsà-òkú: iku yoo jẹun lara wọn; ẹni iduro-ṣinṣin ni yoo jọba wọn ni owurọ; ẹwà wọn yoo si rẹ kúrò, iṣà-òkú si ni ibugbe wọn. (Psm 9:17; Dan 7:18; Mal 4:3; 1 Kor 6:2; Ifh 2:26; Job 24:19.)

15. Ṣugbọn Ọlọrun ni yoo ra ọkan mi lọwọ iṣà-òkú: nitori pe oun o gba mi. (Psm 56:13; 73:24.)

**Ọrọ̀ iyanju ikẹhin.**

16. Iwọ máṣe bẹ̀rù, nitori ẹnikan di ọlọ́rọ̀, nitori iyìn ilé rẹ̀ npọ si i. (Psm 37:7.)

17. Nitori pe, igba ti o bá kú, ki yoo ko ohun kan lọ: ògo rẹ̀ ki yoo sọkalẹ tọ̀ ọ́ lẹhin lọ. (Psm 17:14.)

18. Ni igba ti o wà laaye bi o tilẹ nsure fun ọkàn ara rẹ̀: biotilẹjẹ́ pe a nyin eniyan, ni igba ti oun nṣe rere fun ara rẹ. (Luk 12:19.)

19. Oun yoo lọ si ọdọ ìran awọn baba rẹ̀; wọn ki yoo ri imọlẹ laelae. (Gen 15:15; Job 33:30.)

20. Ọkunrin ti o wà ninu ọlá, ti kò mòye, o dabi ẹranko ti o ṣègbé. (ẹsẹ 12.)

## ORIN 50.

**Oluwa ni onidajọ otitọ.**

OLỌRUN Olodumare, ani Oluwa ni o ti sọrọ, o si pe ayé lati ila-oòrùn wa titi o fi de ìwọ̀ rẹ̀. (Jos 22:22; Psm 113:3.)

2. Lati Sioni wa, pípé ẹwà, Ọlọrun ti tan imọlẹ. (Psm 48:2; Deut 33:2.)

3. Ọlọrun wa nbọ, ki yoo si dákẹ́; iná yoo maa jó niwaju rẹ̀, ẹfuufu líle yoo si maa ja yi i ka kiri. (Psm 96:13; 97:3. Dan 7:10.)

4. Yoo si dó si awọn ọ̀run lati òkè wa, ati si ayé, ki o le maa ṣe ìdájọ́ awọn eniyan rẹ̀. (Deut 4:26; Isa 1:2.)

5. "Kó awọn eniyan mímọ́ mi jọ pọ̀ si ọ̀dọ̀ mi: awọn ti o fi ẹbọ ba mi da majẹmu." (Psm 30:4; Eks 24:7; ẹsẹ 8.)

6. Awọn ọ̀run yoo si sọ̀rọ̀ ododo rẹ̀: nitori Ọlọrun tikararẹ ni onidajọ. (Psm 89:5; 75:7.)

**Idajọ Ọlọrun kii ṣe nipa ohun ti òde ara.**

7. "Ẹ gbọ, ẹ̀yin eniyan mi, emi o sí sọ̀rọ̀; Israẹli, emi o si jẹri si ọ: emi ni Ọlọrun, ani Ọlọrun rẹ. (Psm 81:8; Eks 20:2.)

8. Emi ki yoo ba ọ wí nitori ẹbọ rẹ, ọrẹ-ẹbọ sisun rẹ wa niwaju mi nigba gbogbo. (Psm 40:6; Hos 6:6.)

9. Emi ki yoo mu akọ-malu lati ile rẹ jade, tabi òbukọ ninu agbo-ẹran rẹ. (Psm 69:31.)

10. Nitori gbogbo ẹran igbó ni temi, ati ẹrankẹran lori ẹgbẹrun òkè. (Psm 104:24.)

11. Emi mọ gbogbo ẹyẹ awọn òkè nla: ati ẹranko igbẹ ni temi.

12. "Bi ebi npa mi, emi ki yoo sọ fun ọ: nitori pe ayé ni temi, ati ẹ̀kún inu rẹ. (Eks 19:5.)

13. Emi o ha jẹ ẹran malu, tabi emi a maa mu ẹ̀jẹ̀ ewurẹ bí?

14. Ru ẹbọ-ọpẹ́ si Ọlọrun, ki o si san ẹ̀jẹ́ rẹ fun Ọga-ogo. (Heb 13:15; Deut 23:21.)

15. Ki o si ké pe mi lọ́jọ́ ipọnju: emi o gba ọ, iwọ o si maa yin mi logo" (Psm 91:15; 81:7; 22:23.)

**Ìwà àgàbàgebè ni Ọlọrun bawi.**

16. Ṣugbọn Ọlọrun wi fun eniyan buburu pe, "Ẹtọ́ wo ni o ni lati maa sọrọ ilana mi, tabi ti iwọ fi nfi majẹmu mi si ẹnu rẹ? (Isa 29:13.)

17. Wo ọ, iwọ sá korira ẹkọ, iwọ si ti ṣa ọ̀rọ̀ mi ti lẹhin rẹ. (Rom 2:21,22; Neh 9:26.)

18. Nì igba ti iwọ ri olè, iwọ ba a da ọ̀rẹ́ pọ, iwọ si ba awọn àgbèrè ṣe àjọpín. (Rom 1:32; 1 Tim 5:22.)

19. "Iwọ fi ẹnu rẹ fun buburu, ati ahọn rẹ fun ètè ẹ̀tàn. (Psm 10:7; 52:2.)

20. Iwọ jókòó, iwọ si sọ̀rọ̀ si arakunrin rẹ: iwọ nba orukọ ọmọ ìyá rẹ jẹ́. (Matt 10:21.)

21. Nkan wọnyìí ni iwọ ṣe, emi si dákẹ́; iwọ ṣebi emi tilẹ dabi irú iwọ tikararẹ: emi o ba ọ wi, emi o si ṣí wọn lẹṣẹṣẹ loju rẹ. (Onws 8:11; Isa 42:14; Psm 90:8.)

**Iyọrisi rẹ niyi.**

22. "Njẹ ro eyi, ẹ̀yin ti o gbagbe Ọlọrun, ki emi ma baa fa yin ya pẹ́rẹpẹ̀rẹ ti ko si olugbala. (Job 8:13; Psm 9:17; 7:2.)

23. Ẹnikẹni ti o ba rú ẹbọ ìyìn, o yin mi logo: ati ẹni ti o ba mu ọ̀nà ọ̀rọ̀ rẹ tọ mi emi o fi igbala Ọlọrun hàn fun." (ẹsẹ 14; Psm 85:13; 91:16.)

## ORIN 51.

**Adura Dafidi fun ìdáríjì ati fun ìjẹwọ ẹ̀ṣẹ̀.**

OLỌRUN, ṣaanu fun mi, gẹgẹ bi iṣeun-ifẹ rẹ: gẹgẹ bi ọ̀pọ̀lọpọ̀ aanu rẹ, nu irekọja mi nu kuro. (Psm 4:1; 106:45; Isa 43:25; A.A. 3:19.)

2. Wẹ̀ mi ni àwẹ̀mọ́ kuro ninu aiṣedeede mi ki o si wẹ̀ mi nu kuro ninu ẹ̀ṣẹ̀ mi. (Heb 9:14; 1 Jhn 1:7.)

3. Nitori ti mo jẹ́wọ́ irekọja mi: nigbagbogbo ni ẹ̀ṣẹ̀ mi si nbẹ niwaju mi. (Isa 59:12.)

4. Iwọ, iwọ nikanṣoṣo ni mo ṣẹ̀ si, ti mo ṣe buburu yìí niwaju rẹ? ki a le da ọ láre, nigba ti iwọ ba nsọrọ, ki ara rẹ le mọ, nigba ti iwọ ba nṣe idajọ. (Gen 20:6; Luk 15:21; Rom 3:4.)

5. Kiyesi i, ninu aiṣedeẹde ni a gbe bi mi: ati ninu ẹ̀ṣẹ̀ ni ìyá mi si loyun mi. (Psm 58:3; Job 14:4.)

6. Kiyesi i, iwọ fẹ́ otitọ ni inu: ati níhà ìkọ̀kọ̀ ni iwọ o mu mi mọ ọgbọ́n. (Psm 15:2; Owe 2:6.)

7. Fi ewé-hissopu fọ̀ mi, emi o si mọ: wẹ̀ mi, emi o si fún ju yinyín lọ. (Lef 14:4; Heb 9:19; Isa 1:18.)

8. Mu mi gbọ́ ayọ̀ ati inu didùn; ki awọn egungun ti iwọ ti run le maa yọ̀. (Psm 35:10.)

9. Pa ojú rẹ mọ́ kuro lara ẹ̀ṣẹ̀ mi, ki iwọ si mú gbogbo aiṣedeede mi nù kuro. (Jer 16:17.)

**Ẹ̀jẹ̀ ati Adura Dafidi.**

10. Dá àyà titun sinu mi, Ọlọrun; ki o sì tun ọkan diduro-ṣinṣin ṣe sinu mi. (A.A. 15:9; Ef 2:10; Psm 78:37.)

11. Máṣe ṣa mi ti kuro niwaju rẹ; ki o má si ṣe gba Ẹmi mimọ rẹ lọwọ mi. (A.Ọba 13:23; Ef 4:30.)

12. Mu ayọ̀ igbala rẹ pada tọ̀ mi wá; ki o si fi ẹmi ominira rẹ gbé mi duro. (Psm 13:5; 2 Kor 3:17.)

13. Nigba naa ni emi o maa kọ́ awọn olurekọja ni ọ̀nà rẹ: awọn ẹlẹṣẹ yoo si maa yipada si ọ. (A.A. 9:21,22; Psm 22:27.)

14. Ọlọrun gbà mi lọwọ ẹ̀bi ẹ̀jẹ̀, iwọ Ọlọrun igbala mi: ahọ́n mi yoo si maa kọrin òdodo rẹ kíkan. (2 Sam 12:9; Psm 25:5; 35:28.)

**Onirobinujẹ ati onirora àyà ni Ọlọrun ntẹwọgba.**

15. Oluwa, iwọ ṣi mi ni ètè, ẹnu mi yoo si maa fi ìyìn rẹ hàn: (Psm 9:14.)

16. Nitori iwọ kò fẹ ẹbọ, ti emi iba rú u: inú rẹ kò dun si ọrẹ-ẹbọ sisun. (1 Sam 15:22; Psm 40:4.)

17. Ẹbọ Ọlọrun ni irobinujẹ ọkàn: irobinujẹ ati irora àyà, Ọlọrun, oun ni iwọ ki yoo gàn. (Psm 34:18.)

**Adura Dafidi fun Sioni.**

18. Ṣe rere ni didun inu rẹ si Sioni: iwọ mọ odi Jerusalẹmu. (Isa 51:3; Psm 102:16.)

19. Nigba naa ni inu rẹ yoo dun si ẹbọ ododo; pẹlu ọrẹ-ẹbọ sisun ati ọ̀tọ̀tọ̀ ọrẹ-ẹbọ sisun: nigba naa ni wọn o fi ako-malu rubọ lori pẹpẹ rẹ. (Psm 4:5; 66:13,15.)

## ORIN 52.

**Ipin awọn eniyan buburu.**

EṢE ti iwọ fi nṣe-féfé ninu ìwà-ìkà, iwọ alagbara ọkunrin? Oore Ọlọrun duro pẹ titi. (1 Sam 22:9; Psm 94:4.)

2. Ahọ́n rẹ ngbiro ìwà-ìkà; bi abẹ mimu, o nṣiṣẹ ẹ̀tàn. (Psm 50:19; 57:4; 59:7.)

3. Iwọ fẹ ibi ju ire lọ; ati èké ju ati sọ ododo lọ. (Jer 9:4,5.)

4. Iwọ fẹ ọ̀rọ̀ ipanirun gbogbo, iwọ ahọ́n ẹ̀tàn. (Psm 120:3.)

**Ìgbẹ̀hìn eniyan buburu.**

5. Ọlọrun yoo si lu ọ bolẹ̀ laelae, yoo si di ọ mu, yoo si ja ọ kuro ni ibùjokòó rẹ, yoo si fa ọ tu kuro lori ilẹ̀ alààyè. (Owe 2:22; Psm 27:13.)

6. Olododo yoo ri i pẹlu, yoo si bẹ̀rù, yoo si maa rẹrin rẹ̀ pé. (Job 2:19; Psm 37:34; 40:3.)

7. Kiyesi ọkunrin ti kò fi Ọlọrun ṣe agbara rẹ̀; bikoṣe ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọrọ̀ rẹ̀ ni o gbẹkẹle, o si mu ara rẹ̀ le ninu ìwà-buburu rẹ̀. (Psm 49:6.)

**Ìyìn Olododo.**

8. Ṣugbọn emi dabi igi olifi tútù ni ilé Ọlọrun: emi gbẹkẹle aanu Ọlọrun lae ati laelae. (Jer 11:16; Psm 13:5.)

9. Emi o maa yin o laelae nitori pe iwọ ni o ṣe e: emi o si maa duro de orukọ rẹ; nitori ti o dara ni oju awọn eniyan mimọ́ rẹ. (Psm 30:12; 54:6.)

## ORIN 53.

**Aimoye ati ìwà buburu eniyan.**

AṢIWERE (òmùgọ̀) wi ni ọkàn rẹ̀ pé, Ọlọrun kò sí. Wọn bajẹ wọn si

nṣe irira ẹ̀ṣẹ̀: ko si ẹni ti o nṣe rere. (Psm 14:1–7; Rom 3:10.)
2. Ọlọrun bojuwo ilẹ lati ọ̀run wá sara awọn ọmọ eniyan, lati wò bi ẹnikan wà ti òyẹ yé, ti o si nwa Ọlọrun. (Psm 33:13.)
3. Gbogbo wọn ni o si pada sẹhin; wọn si di eleeri pátápátá; ko si ẹni ti nṣe rere, ko si ẹnikan. (Rom 3:12.)

**Ìjìyà lati ọdọ Oluwa.**

4. Awọn ti nṣiṣẹ ẹ̀ṣẹ̀, ko ní imọ bi? Awọn ẹni ti njẹ eniyan mi bi ẹni jẹun: wọn ko si ke pe Ọlọrun. (Jer 4:22.)
5. Nibẹ ni wọn gbe wa ni ìbẹ̀rù nla nibi ti ẹ̀rù kò gbe si: nitori Ọlọrun ti fọ́n egungun awọn ti o doti ọ ká: iwọ ti dojuti wọn, nitori Ọlọrun ti kẹgan wọn. (Lef 26:17:36; Esk 6:5.)

**Adura fun igbala.**

6. Tani yoo fi igbala fun Israẹli lati Sioni jade wa? Nigba ti Ọlọrun ba mu ìgbèkùn awọn eniyan rẹ pada wá, Jakọbu yoo yọ̀, inu Israẹli yoo si dùn. (Psm 14:7.)

## ORIN 54.

**Ẹ̀sùn ati adura fún iranlọwọ.**

OLỌRUN gbà mi nipa orukọ rẹ, si ṣe idajọ mi nipa agbara rẹ. (Psm 20:1; 2 Kro 20:6.)
2. Gbọ adura mi, Ọlọrun; fi etí si ọ̀rọ̀ ẹnu mi. (Psm 55:1; 5:1.)
3. Nitori ti awọn alejo dide si mi awọn aninilara si nwa ọkan mi: wọn kò ka Ọlọrun si ni oju wọn. (Psm 86:14; 40:14; 36:1.)

**Idaniloju oju rere ati Igbala Ọlọrun.**

4. Kiyesi i, Ọlọrun ni oluranlọwọ mi: Oluwa wa pẹlu awọn ti o gbe ọkan mi duro. (Psm 118:7; 41:12.)
5. Yoo si fi ibi san an fun awọn ọ̀tá mi: ninu otitọ rẹ ge wọn kuro. (Psm 94:23; 143:12; 89:49.)
6. Emi o rubọ atinuwa si ọ: Oluwa, emi o yin orukọ rẹ; nitori ti o dara. (Psm 50:14; 52:9.)
7. Nitori o ti yọ mi kuro nínú ìṣẹ́ gbogbo: oju mi si ri ìfẹ́ rẹ lara awọn ọ̀tá mi. (Psm 34:6; 59:10.)

## ORIN 55.

**Dafidi ṣe apejuwe ìjìyà rẹ.**

FETÍ si adura mi, Ọlọrun; má si ṣe fi ara rẹ pamọ́ kuro ninu ẹ̀bẹ̀ mi. (Psm 61:11; 27:9.)
2. Fiyè sími, ki o si da mi lóhùn: ara mi kò lélẹ̀ ninu àròyé mi, emi si npariwo. (Psm 66:19; 77:3; Isa 38:14.)
3. Nitori ohùn ọ̀tá, nitori inilara eniyan buburu: nitori ti wọn mu ibi ba mi, ati ni ìbínú wọn dẹkùn fun mi. (Psm 17:9; 2 Sam 16:7,8; Psm 71:11.)
4. Àyà dun mi gidigidi ninu mi: ìpáyà ikú si ṣubú lu mi. (Psm 116:3.)
5. Ìbẹ̀rù ati ìwá-rìrì wá si ara mi, ati ìbẹ̀rù ikú bo mi mọlẹ̀. (Psm 119:120; Job 21:6.)
6. Emi si wi pe, A! ìbá ṣe pe emi ni ìyẹ́-apá bi àdàbà! emi iba fò lọ, emi a si sinmi. (Job 3:13.)
7. Kiyesi i, emi iba rìn lọ si ọ̀nà jínjìn rére, emi a si maa gbe ni aginju.
8. Emi iba yara sá asala mi kuro ninu ẹfúùfù líle ati ìjì nla. (Isa 4:6.)

**Iwa arekereke awọn ọ̀rẹ́.**

9. Oluwa, ṣe iparun, ki o si ya wọn ni ahọ́n: nitori ti mo ri ìwà àgbára ati ìjà ni ilu naa. (Jer 6:7.)
10. Ọ̀sán ati ọ̀ru ni wọn fi nrin odi rẹ kiri: ìwà-ìkà pẹlu ati ikaanu nbẹ ni arin rẹ̀.
11. Ìwà buburu nbẹ ni arin rẹ̀: ẹ̀tàn ati èké kò kuro ni igboro rẹ̀. (Psm 5:9; 10:7.)
12. Nitori ti ki i ṣe ọ̀tá ni o gan mi: emi iba pa a mọra: bẹẹ ni ki i ṣe ẹni ti o korira mi ni o gbe ara rẹ ga si mi; njẹ emi iba fi ara mi pamọ kuro lọdọ rẹ̀. (Psm 41:9.)
13. Ṣugbọn iwọ ni, ọkunrin ọgbà mi, amọ̀nà mi, ati ojulumọ mi. (2 Sam 15:12; Psm 41:9; Jer 9:4.)
14. Awa jumọ gbimọ dídùn, awa si kẹ́gbẹ́ rìn wọ ile Ọlọrun lọ. (Psm 42:4.)

15. Kí ikú o de ba wọn, ki wọn o lọ láàyè si Ìṣà-òkú, jẹ́ ki wọn o sọkalẹ̀ si iboji pẹlu ìpáyà, nitori ti ìwà-buburu nbẹ ni ibùjokòó wọn, ati ninu wọn. (Psm 64:7; Num 16:30–33.)

**Igbẹkẹle Dafidi ninu Ọlọrun.**

16. Bi o ṣe temi, emi o ke pe Ọlọrun; Oluwa yoo si gbà mí. (Psm 57:2,3.)

17. Ni alẹ́, ni òwúrọ̀, ati ni ọ̀sán, ni emi o maa gbadura, ti emi o si maa kigbe kíkan: oun o si gbohún mi. (Psm 141:2; Dan 6:10; A.A. 3:1; Psm 5:3.)

18. O ti gba ọkàn mi sílẹ̀ ni alaafia lọwọ ogun ti o ti dó ti mi: nitori pé pẹlu ọpọlọpọ eniyan ni wọn dide si mi. (Psm 103:4; 2 Kro 32:7,8.)

19. Ọlọrun yoo gbọ́, yoo si pọ́n wọn lójú, ani ẹni ti o ti jókòó lati igbaani. Nitori ti wọn kò ni àyípadà, wọn kò si bẹ̀rù Ọlọrun. (Psm 78:59; Deut 33:27.)

20. O si na ọwọ́ rẹ̀ si irú awọn ti o wa ni alaafia pẹlu rẹ̀: o ti da majẹmu rẹ. (Psm 7:4; 89:34.)

21. Ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ̀ kúnná ju òrí–àmọ́ lọ, ṣugbọn ogun jíjà ni o wà ni àyà rẹ̀: ọ̀rọ̀ rẹ̀ kunna ju òróró lọ, ṣugbọn idà fifayọ ni wọn. (Psm 28:3; 57:4; Owe 5:3; Psm 59:7.)

22. Gbe ẹrù rẹ lọ si ọdọ Oluwa, oun ni yoo si mu ọ duro: oun ki yoo jẹ ki ẹsẹ̀ olododo o yẹ lae. (Psm 37:5; Matt 6:25; 1 Pet 5:7; Psm 37:24.)

23. Ṣugbọn iwọ, Ọlọrun, ni yoo mu wọn sọkalẹ̀ lọ si ihò iparun: awọn eniyan ẹ̀jẹ̀ ati eniyan ẹ̀tàn ki yoo pe ààbọ̀ ọjọ wọn; ṣugbọn emi o gbẹkẹle ọ. (Psm 73:18; 5:6; Job 15:32; Owe 10:27; Psm 25:2.)

## ORIN 56.

**Ẹbẹ̀ Dafidi fun ìrànlọ́wọ́.**

OLỌRUN, ṣaanu fun mi: nitori ti eniyan nfẹ gbe mi mì; o nba mi jà lojoojumọ, o nni mi lara. (Psm 57:1–3.)

2. Awọn ọ̀tá mi nfẹ gbe mi mì lojoojumọ: nitori awọn ti nfi igberaga ba mi ja pọ̀. (Psm 57:3; 35:1; 11:1.)

3. Nigba ti ẹ̀rù ba nba mi, emi o gbẹkẹle ọ. (Psm 55:4,5; 11:1.)

4. Nipa Ọlọrun ni emi o maa yin ọ̀rọ̀ rẹ̀, Ọlọrun ni emi o gbẹkẹ mi le, emi ki yoo bẹ̀rù: kinni ẹran-ara le ṣe si mi? (Psm 118:6; Heb 13:6.)

**Arankan awọn ọ̀ta rẹ̀.**

5. Lojojumọ ni wọn nló ọ̀rọ̀ mi: ibi ni gbogbo ìró inú wọn si mi. (Psm 41:7.)

6. Wọn kó ara wọn jọ, wọn ba, wọn kiyesi ìrìn mi, wọn ti nṣọ́nà ọkàn mi. (Psm 59:3; 140:2; 19:10,11.)

7. Wọn hà lè ti ipa aiṣedeede là? Ni ibinu wọ awọn eniyan naa játìlẹ̀, Ọlọrun! (Psm 36:12; 55:23.)

**Igbẹkẹle rè ninu Ọlọrun laisi ibẹ̀rù.**

8. Iwọ nka ìrìn-kiri mi; fi omijé mi sinu ìgò rẹ: wọn kò ha sí ninu ìwé rẹ bí? (Psm 139:3; 39:12; Mal 3:16.)

9. Ni ọjọ́ ti mo ba kígbe, nigba naa ni awọn ọ̀tá mi yoo pẹ̀hìndà: èyí ni emi mọ̀: nitori pe Ọlọrun wà fun mi. (Psm 9:3; 102:2; Rom 8:31.)

10. Ninu Ọlọrun, ọ̀rọ̀ ẹni ti emi o yin, ninu Oluwa, ọ̀rọ̀ eni ti emi o yin,

11. Ọlọrun ni emi gbẹ́kẹ̀ mi lé, emi ki yoo bẹ̀rù kinni eniyan le ṣe si mi?

**Idupẹ nitori idande rẹ̀.**

12. Ẹ̀jẹ́ rẹ nbẹ lara mi, Ọlọrun: emi o fi ìyìn fun ọ. (Psm 50:14.)

13. Nitori pe iwọ ni o ti gba ọkàn mi lọwọ ikú: iwọ ki yoo ha gba ẹsẹ̀ mi lọwọ ìṣubú? Ki Èmi lè maa rin niwaju Ọlọrun ni imọlẹ awọn alààyè? (Psm 116:8; Job 33:30.)

## ORIN 57.

**Adura Dafidi fun ìdándè kuro lọwọ Saulu**

SAANU fun mi: Ọlọrun, ṣaanu fun mi: nitori ti ọkàn mi gbẹ́kẹ̀lé ọ: lootọ, ni ojiji iyẹ-apá rẹ ni emi o fi ṣe aabo mi, titi wahala wọnyìí yoo fi rekọja. (Psm 2:12; 17:8; Isa 26:20.)

2. Emi kigbe sí Ọlọrun Ọga-ogo; si Ọlọrun ti o ṣe ohun gbogbo fun mi. (Psm 138:8.)

3. Oun o ranṣẹ lati ọrun wá, yoo si gbà mi, bi ẹni ti nfẹ gbe mi mì tilẹ nkẹgan mi. Ọlọrun yoo ran aanu rẹ̀ ati otitọ rẹ̀ jade. (Psm 18:16; 56:2; 40:11.)

4. Ọkàn mi wà laarin awọn kinniun: emi tilẹ dubulẹ laarin awọn ti o gbiná, èyiyìí ni awọn ọmọ eniyan, ehín ẹni ti i ṣe ọ̀kọ̀ ati ọfà, ati ahọ́n wọn idà mímú. (Psm 35:17; Owe 30:14; Psm 55:21.)

5. Gbigbe-ga ni ọ, Ọlọrun ju ọrun lọ; ati ogo rẹ̀ ju gbogbo ayé lọ. (Psm 108:5.)

6. Wọn ti ta àwọ̀n sílẹ̀ fun ẹsẹ̀ mi; wọn tẹ orí ọkàn mi ba: wọn ti wà iho sílẹ̀ niwaju mi ni aarin eyíí naa ni awọn tikarawọn jìn sí. (Psm 35:7; 145:14; 7:15; Owe 28:10.)

**Ìyìn ati Ọpẹ́.**

7. Ọkàn mi ti mura, Ọlọrun ọkàn mi ti mura: emi o kọrin, emi o si maa kọrin iyìn. (Psm 108:1.)

8. Jí, ìwọ ogo mi; jí, ohun-èlò orin ati dùùrù: emi tikarami yoo si ji ni kutukutu. (Psm 16:9; 30:12; 150:3.)

9. Emi o ma yin ọ, Oluwa laarin awọn eniyan: emi o si maa kọrin si ọ laarin awọn orilẹ-èdè. (Psm 108:3.)

10. Nitori ti aanu rẹ pọ̀ de ọrun, ati otitọ rẹ dé awọsanma. (Psm 36:5.)

11. Gbigbe-ga ni ọ, Ọlọrun, ju awọn ọrun lọ ati ogo rẹ ju gbogbo ayé lọ. (ẹsẹ 5.)

## ORIN 58.

**Ìjìyà awọn eniyan buburu.**

EYIN ha nsọ ododo nitootọ, ẹ̀yin ìjọ eniyan? Ẹ̀yin ha nṣe idajọ ti o ṣe titọ, ẹ̀yin ọmọ eniyan? (Psm 82:2.)

2. Nitootọ, ẹ̀yin ngbèrò ohun buburu ni àyà yin, ọwọ yin sì na iwa-ipá jade ni ayé. (Mal 3:15; Psm 94:20.)

3. Lati inu ìyá wọn wá ni awọn eniyan buburu ti ṣe ìyapa: wọn ti ṣìnà lojukannaa ti a ti bi wọn, wọn a maa ṣèké. (Psm 51:5; Isa 48:8; Psm 53:3.)

4. Oró wọn dabi oró ẹjò: wọn dabi adití ejò paramọ́lẹ̀ ti o di ara rẹ ni etí: (Psm 140:3; Onws 10:11.)

5. Ti kò fẹ gbọ́ ohùn awọn atuniloju, bi o ti wu ki o maa fi ọgbọ́n ṣe ìtujú tó. (Psm 81:11.)

**Idajọ wọn.**

6. Ká wọn ni ehín, Ọlọrun, ni ẹnu wọn: sì fa ehin-ìbunijẹ awọn ọmọ kinniun ya, Oluwa. (Job 4:10; Psm 3:7.)

7. Ki wọn o yọ̀ danu bi omi ti nṣan nigbagbogbo: nigba ti o ba fa ọrun lati tafà rẹ, ki wọn o dabi ẹni pé a gé wọn ni ijanja. (Jos 7:5; Psm 112:10; 64:3.)

8. Bi ìgbín ti o rẹ̀dànù ti o si ṣègbé: bi iṣẹnu obinrin, bẹẹ ni ki wọn o má ṣe ri òòrùn. (Job 3:16.)

9. Ki ìkòkò yin to mọ̀ ìgbóná ẹ̀gún, iba tutù iba maa jó, jẹ́ ki fi ìjì gbá wọn lọ. (Psm 118:12; Owe 10:25.)

10. Olododo yoo yọ̀ nigba ti o ba ri ẹsan naa: yoo si wẹ̀ ẹsẹ̀ rẹ̀ ninu ẹ̀jẹ̀ awọn eniyan buburu. (Psm 64:10; 91:8; 68:23.)

11. Bẹẹ ni eniyan o si wi pe, "Lootọ, èrè nbẹ fun olododo: lootọ, oun ni Ọlọrun ti o nṣe idajọ ni ayé." (Psm 18:20; 9:8.)

## ORIN 59.

**Adura Dafidi fun idande.**

ỌLỌRUN mi, gbà mi lọwọ awọn ọ̀tá mi: dáàbòbò mi lọwọ awọn ti o dide si mi. (Psm 143:9.)

2. Gbà mi lọwọ awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ̀, ki o si gbà mi sílẹ lọwọ awọn eniyan-ẹ̀jẹ̀. (Psm 23:3; 139:19.)

3. Saa kiyesi i, wọn ba ni bùba fun ọkan mi, awọn alagbara pejọ si mi; ki i ṣe nitori irekọja mi, tabi nitori ẹ̀ṣẹ̀ mi, Oluwa. (Psm 56:6.)

4. Wọn sure, wọn mura ni àìṣẹ̀, mi: dide lati pade mi, ki o si kiyesi i. (Psm 35:19-23.)

5. Nitori naa iwọ, Oluwa, Ọlọrun awọn ọmọ-ogun, Ọlọrun Israẹli, ji lati bẹ gbogbo awọn Keferi wò; máṣe ṣaanu fun awọn olurekọja buburu ni. ( Psm 9:5; Jer 18:23.)

**Igbẹkẹle Dafidi ninu Oluwa.**

6. Wọn pada ni aṣálẹ̀: wọn npariwo bi ajá, wọn nrin yi ilú naa ká. (ẹsẹ 14.)

7. Kiyesi i, wọn nfi ẹnu wọn gùfẹ̀ jade: ida wà ni ètè wọn: nitori ti wọn nwi pe, "Tani o gbọ́?" ( Psm 57:4; 10:11.)

8. Ṣugbọn iwọ, Oluwa, yoo rẹrin wọn: iwọ ni yoo yọṣùtì si gbogbo awọn Keferi. ( Psm 37:13; 2:4.)

9. Agbara rẹ̀ ni emi o duro tì nitori Ọlọrun ni aabo mi. ( Psm 9:9.)

10. Ọlọrun mi ninu iduro ṣinṣin ifẹ rẹ̀ yoo pade mi; Ọlọrun mi yoo mu mi yọ ayọ iṣẹ́gun lori awọn ọta mi. ( Psm 21:3; 54:7.)

**Adura fun iṣẹgun ọ̀tá.**

11. Máṣe pa wọn, ki awọn eniyan mi o má baa gbàgbé: tu wọn ká nipa agbara rẹ; ki o si sọ̀ wọn kalẹ, Oluwa asà wa. (Deut 4:9; Psm 106:27; 84:9.)

12. Nitori ẹ̀ṣẹ̀ ẹnu wọn ni ọ̀rọ̀ ètè wọn, ki a mu wọn ninu igberaga wọn: ati nitori eebu ati èké ti wọn nṣe. (Owe 12:13; Ṣef 3:11; Psm 10:7.)

13. Run wọn ni ibinu, run wọn, ki wọn o má ṣe sí mọ́: ki o si jẹ ki wọn o mọ pe, Ọlọrun ni olori ni Jakọbu titi o fi dé òpin ayé. (Psm 104:35; 83:18.)

14. Ati ni àṣálẹ́ jẹ ki wọn o pada; ki wọn o pariwo bi ajá, ki wọn si ma yi ilu naa ka. (ẹsẹ 6.)

15. Jẹ ki wọn o maa rin sókè rin sódò fun ohun jijẹ, bi wọn kò ba yó, wọn o duro ni gbogbo òru naa.

**Orin ìyìn Dafidi.**

16. Ṣugbọn emi o kọrin agbara rẹ; nitootọ, emi o kọrin aanu rẹ kikan ni òwûrọ̀; nitori pe iwọ ni o ti nṣe ààbò ati ibi-àsálà mi ní ọjọ ipọnju mi. ( Psm 21:13; 101:1; 88:13; ẹsẹ 9; Psm 46:1.)

17. Iwọ, agbara mi, ni emi o kọrin si: nitori Ọlọrun ni ààbò mi, Ọlọrun aanu mi. (ẹsẹ 9,10.)

ORIN 60.

**Adura fun Idande.**

OLỌRUN, iwọ ti ṣá wa tì, iwọ ti tú wa ká, inu rẹ ti bàjẹ́; tun ara rẹ yipada si wa. ( Psm 44:9; 2 Sam 5:20; Psm 79:5; 80:3.)

2. Iwọ ti mu ilẹ̀ wárìrì; iwọ ti fọ́ ọ: mu fífọ́ rẹ̀ bọ̀ sípò: nitori ti o nmi. ( Psm 18:7; 2 Kro 7:14.)

3. Iwọ ti fi ohun ti o ṣòro han awọn eniyan rẹ: iwọ ti mu wa mu ọti-waini itagbọngbọn. ( Psm 71:20; Isa 51: 17–22.)

4. Iwọ ti fi ọpagun fun awọn ti o bẹ̀rù rẹ, ki a le maa fi i hàn nitori otitọ. (Psm 20:5.)

5. Ki a le gba awọn olufẹ rẹ là; fi ọwọ́ ọ̀tún rẹ ṣe igbala, ki o si gbohun mi. (Psm 108:6; 17:7.)

**Gbigba ileri Ọlọrun.**

6. Ọlọrun ti sọ̀rọ̀ ninu ìwà-mímọ́ rẹ̀ pe; Emi o yọ̀, emi o pin Ṣekemu, emi o si wọ̀n afonifoji sukkotu. ( Psm 89:35; Jos 1:6; Gen 12:6.)

7. Ti emi ni Gileadi, ti emi ni Manasse; Efraimu pẹlu ni agbara ori mi; Juda ni olofin mi. (Jos 13:31; Deut 33:17; Gen 49:10.)

8. Moabu ni ìkòkò-ìwẹsẹ̀ mi; lori Edomu ni emi o bọ́ bata mi si; lori Filistini ni mo hó ìhó ìṣẹ́gun. (2 Sam 8:1.)

**Bibẹ̀bẹ̀ fun iranlọwọ.**

9. Tani yoo mu mi wá sinu ilu olodi nì? Tani yoo sin mi lọ si Edomu?

10. Iwọ ha kọ́, Ọlọrun, ẹni ti o sá wa tì? Ati ìwọ, Ọlọrun, ti kò ba ogun wa jade lọ? (ẹsẹ 1; Psm 44:9.)

11. Fun wa ni iranlọwọ ninu ipọnju: nitori pé asán ni iranlọwọ eniyan. ( Psm 146:3.)

12. Nipasẹ Ọlọrun ni awa o ṣe akin; nitori oun ni yoo tẹ awọn ọta wa mọlẹ. (Num 24:18; Psm 44:5.)

ORIN 61.

**Adura Ọkàn ti a ndaamu.**

GBỌ́ ẹkún mi, Ọlọrun; fiyè sì adura mi. (Psm. 64:1; 86:6.)
2. Lati opin ayé wá ni emi o kigbe pe ọ, nigba ti o rẹ àyà mi: fa mi lọ si apata ti o ga jù mi lọ. (Psm 77:3; 18:2.)
3. Nitori iwọ ni o ti nṣe ààbò fun mi, ati ilé-iṣọ agbara lọwọ ọ̀tá. (Psm 62:7; Owe 18:10.)
4. Emi o jókòó ninu àgọ́ rẹ laelae: jẹ ki emi ri ààbò ni iyẹ́-apá rẹ. (Psm 23:6; 91:4.)

**Orin Iyìn.**

5. Nitori pe iwọ, Ọlọrun, ni o ti gbọ́ ẹ̀jẹ́ mi: iwọ ti fi ogún awọn ti o bẹ̀rù orukọ rẹ fun mi. (Psm 56:12; 86:11.)
6. Iwọ o fa ẹmi ọba gùn: ati ọjọ ọdun rẹ̀ ni iran-diran. (Psm 21:4.)
7. Ki oun lè jókòó lori itẹ́ niwaju Ọlọrun laelae; pèsè aanu ati otítọ́ ti yoo maa ṣe itọju rẹ̀. (Psm 41:12; 40:11.)
8. Bẹẹ ni emi o maa kọrin iyìn sí orukọ rẹ laelae, ki emi o le maa san ẹ̀jẹ́ mi ni ojojumọ. (Psm 71:22; 65:1.)

ORIN 62.

**Idanwo igbagbo.**

ỌLỌRUN nikan ni ọkàn mi duro jẹ́ dè; lati ọdọ rẹ̀ wá ni igbala mi. (Psm 33:20.)
2. Oun nikan ni apata mi ati igbala mi; oun ni ààbò mi, emi ki yoo ṣípò pada jọjọ. (Psm 89:26; ẹsẹ 6.)
3. Ẹyin o ti maa rọlu eniyan kan pẹ tó? Gbogbo yin ni o fẹ pa a: bi ogiri ti o bi atí bi ọgba ti nwo lọ. (Isa 30:13.)
4. Kiki ìrò wọn ni lati ja a tilẹ kuro ninu ọlá rẹ: wọn nṣe inu didun ninu èké: wọn nfi ẹnu wọn sure, ṣugbọn wọn ngégùn ni inu wọn. (Psm 4:2; 28:3.)

**Igbẹkẹle igbagbọ.**

5. Ọkàn mi, iwọ sá duro jẹ́ de Ọlọrun; nitori lati ọdọ rẹ̀ wa ni ìrètí mi.
6. Oun nikan ni apata mi ati igbala mi: oun ni ààbò mi; a ki yoo ṣi mi ni ipò. (ẹsẹ 2.)
7. Nipa Ọlọrun ni igbala mi, ati ogo mi: apata agbara mi, ààbò mi si nbẹ ninu Ọlọrun. (Psm 85:9; 46:1.)

**Ọrọ Iyanju si igbagbo.**

8. Gbẹkẹle e nigbagbogbo; ẹyin eniyan, tu ọkàn yin jáde niwaju rẹ; Ọlọrun ààbò fun wa. (Psm 37:3; 1 Sam 1:15; E.Jer. 2:19.)
9. Nitootọ asán ni awọn ọmọ eniyan, èké si ni awọn ọlọ́yè. Wọn goke ninu iwọn, bakannaa ni wọn fẹ́rẹ̀ jù asan lọ. (Psm 39:5–11; Isa 40:15–17; Rom 3:4.)
10. Máṣe gbẹkẹle inilara, ki o má si ṣe gberaga ni olè jíjà: bi ọrọ̀ ba npọ si i, máṣe gbe ọkàn le e. (Isa 30:12; 61:8; Job 31:25; Psm 52:7; 1 Tim 6:7.)
11. Ọlọrun ti sọrọ lẹẹkan; lẹẹkeji ni mo gbọ́ èyí pé, ti Ọlọrun ni agbara. (Job 33:14; 1 Kro 29:11.)
12. Pẹlupẹlu, Oluwa, tirẹ ni aanu: nitori ti iwọ san an fun olukuluku eniyan gẹgẹ bi iṣẹ rẹ̀. (Job 34:11; Matt 16:27; Kol 3:25.)

ORIN 63.

**Ọkàn ti o npoungbẹ fun Ọlọrun.**

ỌLỌRUN, iwọ ni Ọlọrun mi; ni kutukutu ni emi o maa ṣàfẹ́ri rẹ; oungbẹ rẹ ngbẹ ọkàn mi, ẹran-ara mi fà si ọ ni ilẹ gbigbẹ, ati ilẹ ti npoungbẹ, nibi ti omi kò gbe sí. (Psm 42:2; 84:2.)
2. Bayìí ni emi ti wò ọ́ ninu ibi-mímọ́, lati ri agbara rẹ ati ogo rẹ. (Psm 27:4.)
3. Nitori ti iṣeun-ifẹ rẹ san jù iyè lọ, ètè mi yoo maa yin ọ. (Psm 69:16.)
4. Bayìí ni emi o maa fi ibukún fun ọ niwọn bi mo ti wa láàyè: emi o maa gbe ọwọ́ mi soke ni orukọ rẹ. (Psm 104:33; 28:2.)

**Ọkàn ti Ọlọrun ti ba oungbẹ rẹ pade.**

5. Bi ẹni pe ijà ati ọ̀rá bẹẹ ni yoo tẹ

ọkàn mi lọrun; ẹnu mi yoo si maa fi ètè ayọ̀ yin ọ. (Psm 36:8; 71:23.)

6. Nitori ti mo bá ranti rẹ lori ẹní mi, ti emi si nṣe àṣàrò rẹ ni ìṣọ́ òru. (Psm 42:8.)

7. Nitori pe iwọ ni o ti nṣe iranlọwọ mi, nitori naa ní ojiji iyẹ-apa rẹ ni emi o maa yọ̀. (Psm 27:9.)

8. Ọkàn mi ntọ̀ ọ lẹhin gírígírí: ọwọ́ ọ̀tún rẹ ni o gbé mi ró. (Psm 18:35.)

9. Ṣugbọn awọn ti nwa ọkàn mi lati pa a run, wọn o lọ si ìhà isalẹ-ilẹ̀. (Psm 40:14; 55:15.)

10. Wọn o ti ọwọ́ idà ṣubú. Wọn o si ṣe ìjẹ fun kọ̀lọ̀kọ̀lọ̀.

11. Ṣugbọn ọba yoo maa yọ̀ ninu Ọlọrun; olukuluku ẹni ti o nfi i bura ni yoo ṣogo: ṣugbọn awọn ti nṣèkèé ni a o pa ni ẹnu mọ́. (Psm 21:1; Deut 6:13; Isa 45:23.)

## ORIN 64.

**Adura fun iranlọwọ lori awọn ọ̀tá ìkọ̀kọ̀.**

OLỌRUN, gbohun mi ninu àròyé mi: pa ẹmi mi mọ́ lọwọ ẹ̀rù ọta mi. (Psm 55:2; 140:1.)

2. Pa mi mọ́ lọwọ ìmọ̀ ìkọ̀kọ̀ awọn eniyan buburu; lọwọ irukèrudo awọn oniṣẹ-ẹ̀ṣẹ̀. (Psm 56:6; 59:2.)

3. Ẹni ti npọ́n ahọ́n wọn bí ẹni pe idà, ti wọn si fa ọrun wọn le lati tafà wọn, ani ọ̀rọ̀ kíkorò. (Psm 58:7.)

4. Ki wọn o le maa tafà ni ìkọ̀kọ̀ si awọn ti o pé: lojiji ni wọn tafà si i, wọn ko si bẹ̀rù. (Psm 11:2; 55:19.)

5. Wọn gba ara wọn niyanju ni ọ̀ràn buburu: wọn gbìmọ̀ ati dẹkùn silẹ níkọ̀kọ̀; wọn wi pe, "Tani yoo ri wa?" (Psm 10:11.)

6. Wọn gbèrò ẹ̀ṣẹ̀; wọn wi pe, "Awa ti parí èrò ti a gbà tán:" ati ìrò inu olukuluku wọn, ati aya wọn, o jinlẹ. (Psm 49:11.)

**Idajọ Ọlọrun lori awọn eniyan buburu.**

7. Ṣugbọn Ọlọrun yoo tafà si wọn lojiji; wọn o si gbọgbẹ́.

8. Bẹẹ ni ahọ́n wọn yoo mu wọn ṣubú lu ara wọn: gbogbo ẹni ti o ri wọn yoo mi orí wọn. (Psm 9:3; Owe 18:7; Psm 22:7.)

9. Ati gbogbo eniyan ni yoo maa bẹ̀rù, wọn o si maa sọ̀rọ̀ iṣẹ́ Ọlọrun; nitori ti wọn o fi ọgbọ́n rò iṣẹ́ rẹ. (Jer 50:28.)

10. Olododo yoo maa yọ̀ nipa ti Oluwa, yoo si maa gbẹkẹle e; ati gbogbo ẹni-iduro-ṣinṣin ni àyà ni yoo ṣogo. (Psm 32:11; 25:20.)

## ORIN 65.

**Ìyìn tọ́ si Ọlọrun.**

OLỌRUN, ìyìn duro jẹ de ọ ni Sioni; ati si ọ ni a o mu ileri ìfẹ́ ṣẹ. (Psm 116:18.)

2. Iwọ ti ngbọ adura, si ọ̀dọ̀ rẹ ni gbogbo eniyan nbọ̀. (Isa 66:23.)

3. Ọ̀ràn aiṣedeede bori mi: bi o ṣe ti irekọja wa ni, íwọ ni yoo wẹ̀ wọn nu kuro. (Psm 38:4; Heb 9:14.)

4. Alábùkún-fún ni ẹni ti ìwọ yàn, ti iwọ si mu lati maa sunmọ ọdọ rẹ, ki o lè maa gbé inu awọn àgbàlá rẹ: ore inú ile rẹ yoo tẹ́ wa lọ́rùn, àní ti tempili mímọ́ rẹ̀. (Psm 33:12; 4:3; 36:8.)

**Agbara Ọlọrun di mímọ̀.**

5. Ohun ìyanu nipa ododo ni ìwọ fi da wa lóhùn, Ọlọrun ìgbàlà wa: ẹni ti i ṣe igbẹkẹle gbogbo òpin ayé, ati awọn ti o jinna réré ni okun. (Psm 66:3; 85:4; 22:27; 107:23.)

6. Nipa agbara rẹ ẹni ti o fi ìdí oke nla mulẹ ṣinṣin; ti a fi agbara di ni àmùrè: (Psm 93:1.)

7. Ẹni ti o pa ariwo òkun mọ rọ́rọ́, ariwo rírú-omi wọn, ati gìdìgìdì awọn eniyan. (Matt 8:26; Isa 17:12.)

8. Awọn pẹlu ti ngbe apá ipẹkun nbẹru nitori awọn àmì rẹ̀: iwọ mu ijade owurọ ati ti aṣalẹ yọ̀.

**A fi iṣeun Ọlọrun hàn.**

9. Iwọ bẹ ayé wò, o si bomi rin in: iwọ mu un ni ọrọ̀, odò Ọlọrun kún fun omi: iwọ pèsè ọkà wọn, nigba ti iwọ

pèsè ilẹ bẹẹ. ( Psm 68:9,10; 46:4; 104:14.)

10. Iwọ bomin-rin aporo rẹ̀ pupọ-pupọ; iwọ si tẹ ògúlùtu rẹ̀: iwọ fi ọ̀wọ òjò mu ilẹ rọ̀: iwọ busi hihu rẹ̀.

11. Iwọ fi oore rẹ de ọdun ni adé; ọ̀rá nkán ni ipa-ọ̀nà rẹ.

12. Papa-tútù aginju nkán: awọn òkè kékèké fi ayọ̀ di ara wọn ni amure. (Job 38:26,27; Psm 98:8.)

13. Agbo ẹran ni a fi wọ papa-tutu naa, ni aṣọ: afonifoji ni a fi ọkà bo mọlẹ: wọ́n hó fun ayọ̀, wọn nkọrin pẹlu. ( Psm 144:13; 72:16; 98:8.)

## ORIN 66.

**Orin Ọpẹ́: Fun idande Orilẹ-ede.**

EHÓ ìhó ayọ̀ sí Ọlọrun, ẹ̀yin ilẹ̀ gbogbo: ( Psm 100:1.)

2. Ẹ kọrin ọlá orukọ rẹ̀: ẹ fun un ní ìyìn ogo. ( Psm 81:1; 79:9.)

3. Ẹ wi fun Ọlọrun pé, Iwọ ti ni ẹ̀rù to ninu iṣẹ́ rẹ! nipa ọ̀pọ̀ agbara rẹ ni awọn ọ̀tá rẹ yoo fi sìn ọ́. ( Psm 65:5; 18:44.)

4. Gbogbo ayé ni yoo maa sìn ọ́, wọn o si maa kọrin si ọ; wọn o maa kọrin si orukọ rẹ. ( Psm 22:27; 67: 3,4.)

5. Ẹ wá wo iṣẹ́ Ọlọrun, o ni ẹ̀rù ni ìṣe rẹ̀ si awọn ọmọ eniyan. ( Psm 46:8; 106:22.)

6. O sọ òkun di ilẹ̀ gbígbẹ: wọn fi ẹsẹ̀ la odò já: nibẹ ni awa yọ̀ ninu rẹ̀. (Eks 14:21; Jos 3:6; Psm 105:43.)

7. O jọba nipa agbara rẹ̀ laelae; ojú rẹ̀ nwo awọn orilẹ-èdè ki awọn ọlọtẹ máṣe gbe ara wọn ga. ( Psm 145:13; 11:4; 140:8.)

8. Ẹ fi ibukun fun Ọlọrun wa, ẹ̀yin eniyan, ki ẹ si mu ni gbọ́ ohùn ìyìn rẹ̀. ( Psm 98:4.)

9. Ẹni ti o mu ẹ̀mí wa wà laaye, tí kò sí jẹ ki ẹsẹ̀ wa yẹ̀. ( Psm 121:3.)

10. Ọlọrun, nitori ti iwọ ti ridi wa: iwọ ti dán wa wò, bi a ti ndán fadaka wò. ( Psm 17:3; Isa 48:10;Sek 13: 9.)

11. Iwọ mu wa wọ inú àwọ̀n; iwọ fi ipọnju le wa ni ẹ̀gbẹ́. (E.Jer. 1:13.)

12. Iwọ mu awọn eniyan gùn wa lori: awa nwọ inu iná ati omi lọ, ṣugbọn ìwọ̀ mu wa jade wá si ibi irọra. (Isa 51:23; 43:2.)

**Fun iranlọwọ.**

13. Emi o lọ sinu ilé rẹ, emi pẹlu ẹbọ sisun; emi o san ẹ̀jẹ́ mi fun ọ. (Onws 5:4.)

14. Ti ètè mi ti jẹ́, ti ẹnu si ti sọ, nigba ti mo wa ninu ipọnju. ( Psm 18:6.)

15. Emi o rú ẹbọ sisun ọlọra si ọ, pẹlu oorun ọ̀rá àgbò: emi o rubọ akọ-malu pẹlu ewurẹ. ( Psm 51:19; Num 6:14.)

16. Ẹ wá gbọ̀, gbogbo ẹ̀yin ti o bẹ̀rù Ọlọrun, emi o sọ ohun ti o ṣe fun ọkàn mi. ( Psm 34:11; 71:15,24.)

17. Emi fi ẹnu mi kigbe pè é, emí o si fi ahọ́n mi buyìn fun un.

18. Bi emi ba gba ẹ̀ṣẹ̀ ni àyà mi, Oluwa ki yoo gbohùn mi: (Job 36:21; Isa 1:15; Jak 4:3.)

19. Ṣugbọn nitootọ Ọlọrun ti gbó-hùn mi: o si ti fi etí sí ohùn adura mi. ( Psm 116:1,2.)

20. Olubukun ni Ọlọrun, ti kò yi adura mi pada kuro, tabi aanu rẹ̀ kúrò lọdọ mi. ( Psm 68:35; 22:24.)

## ORIN 67.

**Orin Ibukun.**

KI Ọlọrun o ṣaanu fun wa, ki o si busi i fun wa; ki o si ṣe ojú rẹ̀ ki o mọlẹ si wa lara, (Num 6:25; Psm 4:6.)

2. Ki ọ̀nà rẹ̀ le di mímọ̀ ni ayé, ati igbala ilera rẹ̀ ni gbogbo orilẹ-ede (A.A. 18:25; Tit 2:11.)

3. Jẹ ki awọn eniyan o yin ọ, Ọlọrun; jẹ ki gbogbo eniyan o yin ọ.

4. Jẹ ki inu awọn orilẹ-ede o dun, ki wọn maa kọrin fun ayọ: nitori ti iwọ o fi ododo ṣe idajọ eniyan, iwọ o si jọba awọn orilẹ-ede ni aye. (Psm 96:10; 98:9.)

5. Jẹ ki awọn eniyan o yin ọ, Ọlọrun; jẹ ki gbogbo eniyan o yin ọ. (ẹsẹ 3.)

6. Nigba naa ni ilẹ yoo to maa mu àsunkún rẹ wá; Ọlọrun, Ọlọrun wa tikararẹ yoo busi i fun wa. (Lef 26:4; Psm 85:12; Esk 34:27.)

7. Ọlọrun yoo busi i fun wa; ati gbogbo òpin ayé yoo si maa bẹ̀rù rẹ. (Psm 33:8.)

ORIN 68.

**Ọlọrun ti o mu awọn eniyan rẹ jade.**

KI Ọlọrun dide, ki a si tú awọn ọ̀tá rẹ ká: ki awọn ti o korira rẹ pẹlu, ki wọn salọ kuro niwaju rẹ. (Num 10:35; Isa 33:3.)

2. Bi eefin ti nfẹ lọ, bẹẹ ni ki o fẹ wọn lọ; bi idà ti nyọ́ niwaju iná bẹẹ ni ki eniyan buburu ṣègbé niwaju Ọlọrun. (Isa 9:18; Hos 13:3; Psm 97:5; Mika 1:4.)

3. Ṣugbọn jẹ ki inu awọn olododo ó dùn; ki wọn ó yọ̀ gidigidi. (Psm 32:11.)

4. Ẹ kọrin si Ọlọrun, ẹ kọrin iyìn si orukọ rẹ; ẹ la ọ̀nà fun ẹni ti nrekọja ni aginjù. JAH ni orukọ rẹ, ki ẹ si maa yọ̀ niwaju rẹ. (Psm 66:2; Isa 57:14; 40:3; Psm 83:18.)

5. Baba awọn alainibaba ati onidajọ awọn opó ni Ọlọrun ni ibùgbé rẹ mímọ́. (Psm 146:9; Deut 10:18; 26:15.)

6. Ọlọrun mu ẹni-òfo jókòó ninu ilé: o mu awọn ti a dè ni ẹ̀wọ̀n jade wá si ìrọra; ṣugbọn awọn ọlọ̀tẹ̀ ni ngbe inu ilẹ̀ gbigbẹ. (Psm 113:9; A.A. 21:6; Psm 107:34.)

**Ọlọrun ti o mu awọn eniyan rẹ la aginju.**

7. Ọlọrun, nigba ti iwọ jade lọ niwaju awọn eniyan rẹ, nigba ti iwọ nrin lọ laarin aginjù. (Eks 13:21; Ondj 4:14.)

8. Ilẹ mi, ọrun dà silẹ̀ niwaju Ọlọrun: ani Sinai tikararẹ mi niwaju Ọlọrun, Ọlọrun Israẹli. (Eks 19:16, 18; Ondj 5:4.)

9. Ọlọrun iwọ ni o rán ọpọlọpọ òjò si ilẹ̀-ini rẹ, nigba ti o rẹ̀ ẹ tán, iwọ tù u lara. (Deut 11:11.)

10. Ijọ eniyan rẹ ni o tẹ̀dó sinu rẹ: iwọ Ọlọrun ninu ore rẹ ni o ti pèsè fun awọn talaka. (Deut 26:5; Psm 74:19.)

**Ọlọrun ti o ṣẹgun.**

11. Oluwa ti sọ̀rọ̀: ọpọlọpọ si ni ogun awọn ẹni ti nfi ayọ̀ ròhìn rẹ̀:

12. Awọn ọba ẹgbẹ ogun sá, wọn sá lọ: obinrin ti o si jókòó ni ilé ni npin ikogun naa: (Psm 135:11; 1 Sam 30:24.)

13. Nigba ti ẹ̀yin dubulẹ laarin agbo ẹran, nigba naa ni ẹyin ó dàbí apá àdàbà ti a bò ni fàdákà, ati iyẹ́ rẹ̀ pẹlu wúrà pupa. (Gen 49:14.)

14. Nigba ti Olodumare tú awọn ọba ká ninu rẹ̀, o dabi òjò-didi ni Salmoni. (Jos 10:10.)

**Ọlọrun Sioni.**

15. Oke Ọlọrun ni òkè Baṣani: òkè ti o ni orí pupọ ni òkè Baṣani.

16. Eeṣe ti ẹ̀yin nfi ilara wò, ẹ̀yin òkè, oke naa ti Ọlọrun fẹ lati maa gbe? Nitootọ, Oluwa yoo maa gbe ibẹ laelae. (Deut 12:5; Psm 87:1,2.)

17. Ẹgbẹ̀rún mẹwàá meji lọ́na ẹgbẹẹgbẹ̀rún ni kẹkẹ́-ogun Ọlọrun, ani ẹgbẹẹgbẹ̀rún lọ́na ẹgbẹẹgbẹ̀rún: Oluwa nbẹ laarin wọn ni Sinai ni ibi mímọ́.

18. Iwọ ti goke si ibi giga, iwọ ti di igbèkùn ni igbekun lọ: iwọ ti gba ẹ̀bùn fun eniyan: nitootọ, fun awọn ọlọ̀tẹ̀ pẹlu, ki Oluwa Ọlọrun le maa ba wọn gbe. (A.A. 1:9; Ef 4:8; Ondj 5:12; 1 Tim 1:13.)

**Ọlọrun olugbala.**

19. Olubukun ni Oluwa lojojumọ, bi a di ẹrù rù wa; Ọlọrun naa ni igbala wa. (Psm 55:22; 65:5.)

20. Ẹni ti i ṣe Ọlọrun wa ni Ọlọrun igbala; ati lọwọ Jehofah Oluwa, ni àjàbọ́ lọwọ ikú wà. (Psm 49:15; 56:13.)

21. Nitori Ọlọrun yoo fọ́ orí awọn ọta rẹ, ati agbárí onirun ti irù ẹni ti nrin sibẹ ninu ẹ̀ṣẹ̀. (Psm 110:6; 55:23.)

22. Oluwa wi pe, emi o tun pada lati Başani wá, emi o tun mu wọn pada lati ibú òkun wá. (Num 21:33; Eks 14:22.)

23. Ki ẹsẹ̀ rẹ le pọ́n ninu ẹ̀jẹ̀ awọn ọ̀tá rẹ, ati ahọ́n awọn ajá rẹ ninu rẹ naa. ( Psm 58:10; 1 A.Ọba 21:19.)

**Ọlọrun ibi mímọ́.**

24. Wọn ti rí ìrìn rẹ, Ọlọrun ani ìrìn Ọlọrun mi, Ọba mi, sinu ibi mímọ́. ( Psm 77:13; 63:2.)

25. Awọn akọrin lọ niwaju, awọn olohun-èlò orin kẹhin laarin awọn ọmọbinrin ti wọn nlu ìlù. (1 Kro 13:8; Ondj 11:34.)

26. Ẹ fi ibukun fun Ọlọrun ni ẹgbẹẹgbẹ, ani fun Oluwa, ẹ̀yin ti o ti orisun Israẹli wá. ( Psm 26:12; Deut 33:28; Isa 48:1.)

27. Nibẹ ni Bẹnjamini kekere wà, pẹlu olori wọn, awọn ọmọ-alade Juda pẹlu awọn igbimọ wọn, awọn ọmọ-alade Sebuluni, ati awọn ọmọ-alade Naftali. (1 Sam 9:21.)

**Gbogbo orilẹ-ede ni o mọ Ọlọrun.**

28. Ọlọrun rẹ ti paṣẹ agbara rẹ: Ọlọrun fi ẹsẹ̀ eyi ti o ti ṣe fun wa múlẹ̀.

29. Nitori tẹmpili rẹ ni Jerusalẹmu ni awọn ọba yoo maa mu ọrẹ wa fun ọ. (Psm 72:10.)

30. Bá awọn ẹranko eesú wí, ọ̀pọ̀lọpọ̀ awọn akọ-malu, pẹlu awọn ọmọ-malu eniyan, titi olukuluku yoo fi foribalẹ pẹlu iwọn fadaka: tu awọn eniyan ti nṣe inu didun si ogun ká. ( Psm 22:12; 89:10.)

31. Awọn ọmọ-alade yoo ti Egipti jade wa; ni isinsinyìí ni Etiopia yoo na ọwọ́ rẹ̀ si Ọlọrun. (Isa 19:19; 45:14.)

**Ìyìn fun Ọlọrun gbogbo àgbáyé.**

32. Ẹ kọrin si Ọlọrun, ẹ̀yin ijọba ayé; ẹ kọrin ìyìn si Oluwa.

33. Sí ẹni ti ngùn ati ọ̀run de ọ̀run àtijọ́; o! ó fọhùn rẹ̀, eyí, naa ni ohùn nla. ( Psm 18:10; Deut 10:14; Psm 44:6; 29:4.)

34. Ẹ yọ̀nda agbara fun Ọlọrun; ọla-nla rẹ̀ wà lori Israẹli, ati agbara rẹ̀ nbẹ ni àwọ̀sánmà. ( Psm 29:1.)

35. Ọlọrun, iwọ ni ẹ̀rù lati ibi mimọ rẹ wa: Ọlọrun Israẹli ni Oun, ti nfi ìlera ati agbara fún awọn eniyan rẹ̀, "Olubukun ni Ọlọrun!" ( Psm 47:2; 29:11; 66:29.)

## ORIN 69.

**Adura ati awọn ìṣòro Olórin naa.**

OLỌRUN, gbà mi; nitori ti awọn omi ti wọ inu lọ si ọkàn mi. (ẹsẹ 14,15.)

2. Emi rì ninu irà jínjìn, nibi ti ìbi-ìdúró ko si, emi de inú awọn omi jín-jìn, nibi ti ìṣán-omi ṣan bo mi lórí. (Psm 40:2; Jona 2:3.)

3. Agara ẹkún mi dá mi: ọ̀fun mi gbẹ: ojú mi ṣu nigba ti emi duro de Ọlọrun mi. ( Psm 6:6; 119:82; Isa 38:14.)

4. Awọn ti o korira mi laninidi ju irun orí mi lọ: awọn ti nṣe ọ̀tá mi laiṣẹ ti iba pa mi run, wọn lagbara: nigba naa ni mo san ohun ti emi kò mú. ( Psm 35:19; Jhn 15:25; Psm 38:19; 35:11.)

5. Ọlọrun, iwọ mọ wèrè mi, ẹ̀ṣẹ̀ mi ko si pa-mọ loju rẹ. ( Psm 38:5; 44:21.)

6. Oluwa, Ọlọrun awọn ọmọ-ogun, máṣe jẹki ojú ki o ti awọn ti o duro de ọ nitori mi: máṣe jẹki awọn ti nwa ọ ó damu nitori mi, Ọlọrun Israẹli. (2 Sam 12:14.)

7. Nitori pe nitori tirẹ ni emi ṣe nru ẹ̀gàn; ìtìjú ti bo mi loju. (Jer 15:15; Psm 44:15.)

8. Emi di àjèjì sí awọn arakunrin mi, ati àlejò si awọn ọmọ ìyá mi. ( Psm 31:11; Isa 53:3.)

9. Nitori tí itara ilẹ rẹ ti jẹ mi tán; ati ẹ̀gàn awọn ti o gàn ọ́, ṣubú lu mi. (Jhn 2:17; Psm 89:50.)

10. Nigba ti mo sọkún, ti mo si nfi ààwẹ̀ jẹ ara mi ni ìyà, eyi naa si di ẹ̀gàn mi. (Psm 35:13.)

11. Emi fi aṣọ ọ̀fọ̀ ṣe aṣọ mi pẹlu:

mo si di ẹni-òwe fun wọn (Psm 35:13; Jer 24:9.)

12. Awọn ti o jókòó ni ẹnu-bode nsọrọ si mi; emi si di orin awọn ọmuti (Job 30:9.)

**Adura fun ìgbàlà.**

13. Ṣugbọn bi o ṣe temi ni, iwọ ni emi ngbadura mi si, Oluwa, ní ìgbà itẹwọgba: Ọlọrun, ninu ọpọlọpọ aanu rẹ da mi lohun, ninu òtítọ igbala rẹ. (Isa 49:8; 2 Kor 6:2; Psm 51:1.)

14. Yọ mi kuro ninu ẹrẹ, ma si ṣe jẹ ki emi ri: gbígbà ni ki a gba mi lọwọ awọn ti o korira mi, ati ninu awọn omi jinjin. (ẹsẹ 2; Psm 144:7.)

15. Máṣe jẹ ki íkún-omi bo mi mọlẹ, bẹẹ ni ki o maṣe jẹ ki ọgbun ó gbé mi mì, ki o má si ṣe jẹ ki ihò pa ẹnu rẹ dé mọ mi. (Psm 124:4,5; Num 16:33.)

16. Oluwa, dá mi lóhun; nitori iṣeun ifẹ rẹ dara, yipada si mi gẹgẹ bí ọpọlọpọ irọnu aanu rẹ. (Psm 63:3; 51:1; 25:16.)

17. Ki o má si ṣe pa ojú rẹ mọ kuro lara iranṣẹ rẹ: emi sá wa ninu ipọnju, yára, da mi lóhùn. (Psm 27:9; 66:14.)

18. Sunmọ ọkàn mi, sì ra a pada; gba mi nitori awọn ọ̀tá mi. (Psm 49:15.)

19. Iwọ ti mọ ẹ̀gàn mi ati ìtìjú mi, ati alailọla mi: gbogbo awọn ọ̀tá mi ni o wa niwaju rẹ; (Psm 22:6,7; Isa 53:3.)

20. Ẹ̀gàn ti ba mi ni inú jẹ́: emi si kún fún ikaanu; emi si wòyé fun ẹni ti yoo ṣaanu fun mi, ṣugbọn kò sí: ati fun awọn olutunu, emi kò sì ri ẹnikan. (Jer 23:9; Isa 63:5; Job 16:2.)

21. Wọn fi ọroro fun mi pẹlu ni ohun jíjẹ mi; ati ni oungbẹ mi wọn fun mi ni ọti kíkan lati mu. (Matt 27:34; Jhn 19:29.)

**Adura iṣẹgun lori awọn ọ̀tá.**

22. Jẹ ki tabili wọn o di ìkẹkùn niwaju wọn: fun awọn ti o wà ni alaafia ki o si di okùn dídẹ. (Rom 11:9,10.)

23. Jẹ ki ojú wọn ó ṣú, ki wọn má riran, ki o si maa mú ẹ̀gbẹ́ wọn gbọ̀n nigbagbogbo. (Isa 6:9,10; Dan 5:6.)

24. Da irunu rẹ si wọn lori, si jẹ ki ikannu ibinu rẹ o lé wọn bá. (Psm 79:6.)

25. Jẹ ki ibùgbé wọn di ahoro; ki ẹnikẹni máṣe gbé inú àgọ wọn. (Matt 23:38; A.A. 1:20.)

26. Nitori ti wọn nṣe inunibini si ẹni ti iwọ ti lù; wọn si nsọrọ ibanujẹ ti awọn tí iwọ ti ṣa ni ọgbẹ́. (Isa 53:4.)

27. Fi ẹ̀ṣẹ̀ kun ẹ̀ṣẹ̀ wọn; ki o ma si ṣe jẹ́ ki wọn o wá sinu ododo rẹ.

28. Pa orukọ wọn rẹ́ kuro ninu ìwé awọn alààyè, ki a má si kọwe wọn pẹlu awọn olododo. (Eks 32:32; Filp 4:3; Luk 10:20.)

**Orin ìyìn ati idanilọju.**

29. Ṣugbọn talaka ati ẹni-ikaanu lèmi, Ọlọrun jẹ́ kí igbala rẹ gbe mi lékè. (Psm 70:5; 59:1.)

30. Emi o fi orin yin orukọ Ọlọrun, emi o si fi ọpẹ́ gbe orukọ rẹ ga. (Psm 28:7; 34:3; 50:14.)

31. Èyí pẹlu ni yoo wù Oluwa ju ọda-malu tabi akọ-malu lọ ti o ni ìwo ati bàtà ẹsẹ̀. (Psm 50:13:14.)

32. Awọn onirẹlẹ yoo ri èyií, inú wọn o si dùn; ọkàn ẹyin ti nwa Ọlọrun yoo si wa lááyè. (Psm 34:2; 22:26.)

33. Nitori ti Oluwa gbóhùn awọn talaka, kò si fi ojú pa awọn ará tubu rẹ́. (Psm 12:9; 68:6.)

34. Jẹ ki ọrun ati ayé yin ín, òkun ati ohun gbogbo ti nrákò ninu wọn. (Psm 96:11; 148:1; Isa 44:23; 49:13.)

35. Nitori ti Ọlọrun yoo gbà Sioni là, yoo si kọ́ awọn ilú Juda wọnyií: ki wọn o le maa gbe ibẹ̀, ki wọn o le maa ni i ni ilẹ-iní. (Psm 51:18; Isa 44:26.)

36. Iru-ọmọ awọn iranṣẹ rẹ pẹlu ni yoo maa jogún rẹ: awọn ti o si fẹ́ orukọ rẹ ni yoo maa gbe inu rẹ̀. (Psm 102:28; 37:29.)

## ORIN 70.

**Idande kuro lọwọ olujẹni-níyà.**

OLỌRUN, yára gba mi; Oluwa, yara lati ran mi lọ́wọ́. (Psm 40:13.)

2. Ki ojú o ti awọn ti nwá ọkàn mi,

ki wọn ọ si daamu: ki wọn si pada sẹhin, ki a daamu awọn ti nwa ifarapa mi. (Psm 35:4,26.)

3. Ki a pa wọn lẹhin da fun èrè ìtìjú awọn ti nwi, pe, "A! a!" (Psm 40:15.)

4. Ki gbogbo awọn ti nwa ọ maa yọ̀, ki inú wọn si maa dun nipa tirẹ: ki irú awọn ti o si fẹ́ ìgbàlà rẹ maa wi nigbagbogbo pé, "Ki a gbe Ọlọrun ga!"

5. Ṣugbọn talaka ati alaini ni emi: Ọlọrun, yara si mi: iwọ ni oluranlọwọ ati olugbala mi: Oluwa, máṣe pẹ titi. (Psm 40:17; 141:1.)

## ORIN 71.

**Ẹbẹ̀ fun Iranlọwọ.**

OLUWA, iwọ ni mo gbẹkẹ mi le: lae máṣe jẹ ki a daamu mi. (Psm 25:2,3.)

2. Gba mi nipa ododo rẹ, ki ó si mu mi yọ̀: dẹ etí rẹ si mi ki o si gba mi. (Psm 31:1; 17:6.)

3. Iwọ ni ki o ṣe ibi isadi apata mi, nibi ti emi o maa wọ̀ nigbagbogbo iwọ ti paṣẹ lati gba mi: nitori iwọ ni apata ati odi agbara mi. (Psm 31:2,3; 44:4.)

4. Gbà mi, Ọlọrun mi, lọwọ awọn eniyan buburu, lọwọ alaiṣododo ati ìkà ọkunrin. (Psm 140:1,4.)

5. Nitori iwọ ni ireti mi, Oluwa Ọlọrun; iwọ ni igbẹkẹle mi lati igba èwe mi. (Jer 17:7.)

6. Ọwọ́ rẹ ni a ti fi gbé mi dúró lati inú wá: iwọ ni ẹni ti o mu mi jade lati inu ìyá mi wá: nipasẹ rẹ ni ìyìn mi wa nigbagbogbo. (Psm 22:9,10; Isa 46:3; Psm 34:1.)

7. Emi dabi ẹni-iyanu fun ọpọlọpọ eniyan, ṣugbọn ìwọ ni aabo mi ti o lagbara. (1 Kro 4:9; Psm 61:3.)

8. Jẹ ki ẹnu mi o kún fun ìyìn rẹ ati fun ọlá rẹ lọjọ gbogbo. (Psm 35:28.)

9. Máṣe ṣa mi tì ni igba ogbó, máṣe kọ̀ mi silẹ nigba tí agbara mi bá yẹ̀. (ẹsẹ 18.)

10. Nitori awọn ọ̀tá mi nsọrọ̀ si mi; awọn ti nṣọ ọkàn mi si gbìmọ̀ pọ̀. (Psm 56:6; Matt 27:1.)

11. Wọn wi pe, "Ọlọrun ti kọ ọ silẹ: ẹ lepa ki ẹ si mu un: nitori ti ko si ẹni ti yoo gba a." (Psm 3:2; 7:2.)

12. Ọlọrun, maṣe jinna si mi: Ọlọrun mi, yara si iranlọwọ mi. (Psm 35:22; 70:1.)

13. Jẹ ki wọn o daamu, ki a si run awọn ti nṣe ọ̀tá ọkàn mi, ki a si fi ẹ̀gàn ati abuku bò awọn ti nwá ifarapa mi. (Psm 35:4; 109:29; ẹsẹ 24.)

14. Ṣugbọn emi o maa reti nigbagbogbo, emi o si maa fi ìyìn kun ìyìn rẹ.

15. Ẹnu mi yoo maa fi ododo rẹ ati ìgbàlà rẹ han lọjọ gbogbo; emi kò sa mọ iye rẹ. (Psm 35:28; 40:5.)

16. Emi o wa ninu agbara Oluwa Ọlọrun; emi o maa dá ọ̀rọ̀ ododo rẹ sọ, ani tirẹ̀ nikan, (Psm 106:2; 51:14.)

17. Ọlọrun, iwọ ti kọ́ mi lati ìgbà èwe mi wá: ati di isinsinyìí ni emi ti nsọrọ iṣẹ́ iyanu rẹ. (Deut 4:5; 6:7; Psm 26:7.)

18. Pẹlupẹlu, nigba ti emi di arúgbón tán ti mo hewú, Ọlọrun máṣe kọ mí títí emi o fi fi ipa rẹ han ìran yìí, ati agbara rẹ fun gbogbo awọn ará ẹhin. (ẹsẹ 9.)

19. Ọlọrun, ododo rẹ ga jọjọ pẹlu, eniti o ti nṣe nkan nla, Ọlọrun, tani o dati iwọ! (Psm 57:10; 35:10.)

**Orin igbẹkẹle ati ìyìn fun idande.**

20. Iwọ ti o fi ìdààmú nla ati kikan hàn mi, ni yoo si tún mi jí, yoo si tun mu mi sọ̀ si òkè lati ọ̀gbun ilẹ̀ wá. (Psm 60:3; Hos 6:1,2.)

21. Iwọ o sọ ọlá mi di púpọ̀, iwọ o si tù mi ninu nihà gbogbo.

22. Emi o si fi ohun-èlò orin yìn ọ pẹlu, ani fun otitọ rẹ, Ọlọrun mi; iwọ ni emi o maa fi dùùrù kọrin sí, iwọ Ẹni-Mimọ Israẹli. (O.D. 33:2; 78:41.)

23. Ètè mi yoo yọ̀ gidigidi, nigba ti mo bá nkọrin si ọ: ati ọkàn mi, ti iwọ ti rapada. (Psm 5:11; 103:4.)

24. Ahọ́n mi pẹlu yoo si maa sọrọ ododo rẹ titi ni ọjọ gbogbo: nitori ti wọn daamu, a si doju ti awọn ti nwa ifarapa mi. (Psm 35:28; ẹsẹ 13.)

## ORIN 72.

**Adura fun oba fun idajọ.**

OLỌRUN, fi idajọ rẹ fun ọba, ati ododo rẹ fun ọmọ ọba. (Psm 24:5.)

2. Oun o maa fi ododo ṣe idajọ awọn eniyan rẹ, yoo si maa fi ẹ̀tọ́ ṣe idajọ awọn tálákà rẹ. (Isa 9:7; Psm 82:3.)

3. Awọn òkè nla yoo maa mu alaafia fun awọn eniyan wá, ati awọn òkè kekere nipa ododo. (Psm 85:10; Isa 32:17.)

4. Oun o maa ṣe idajọ awọn talaka eniyan, yoo maa gba awọn ọmọ awọn alaini yoo si fà aninilara ya pẹ́rẹ-pẹ̀rẹ. (Isa 11:4.)

**Adura fun ọjọ pípẹ́.**

5. Wọn o si maa bẹ̀rù rẹ, niwọn bi òòrùn ati oṣupa yoo ti pẹ́ tó, lati irandiran. (Psm 89:36.)

6. Oun o rọ̀ si ilẹ bi òjò si orí koriko ìrẹ́-mọ́lẹ̀: bi ọwọ òjò ti o rin ilẹ. (2 Sam 23:4; Hos 6:3.)

7. Ni ọjọ́ rẹ̀ ni awọn olododo yoo gbilẹ̀: ọpọlọpọ alaafia niwọn bi oṣupa yoo ti pẹ tó. (Psm 92:12.)

**Adura fun ijọba.**

8. Oun o si jọba lati òkun dé òkun, ati lati odò dé òpin ayé. (Eks 23:31; Sek 9:10.)

9. Awọn ti ngbé ni aginju yoo tẹriba fun un; awọn ọ̀ta rẹ yoo si lá erupẹ ilẹ̀. (Psm 74:14; Isa 49:23; Mika 7:17.)

10. Awọn ọba Tarṣiṣi, ati ti awọn erekuṣu yoo mu ọrẹ wá: awọn ọba Seba ati ti Seba yoo mu ẹ̀bùn wá. (2 Kro 9:21; Psm 68:29.)

11. Nitootọ, gbogbo awọn ọba ni yoo wólẹ̀ niwaju rẹ̀: gbogbo awọn orilẹ-ede ni yoo maa sìn in. (Psm 49:23.)

**Adura fun àánú.**

12. Nitori yoo gba aláìní nigba ti o ba nké: talaka pẹlu, ati ẹni ti ko ni oluranlọwọ. (Job 29:12.)

13. Oun o dá talaka ati alaini sí, yoo si gba ọkàn awọn alaini là.

14. Oun o ra ọkàn wọn pada lọwọ ẹ̀tàn ati iwà-ipà: iyebíye si ni ẹ̀jẹ̀ wọn lójú rẹ̀. (Psm 116:15.)

**Adura fun oruko pípẹ́.**

15. Oun o si yè, oun ni a o si fi wúrà Ṣeba fún: a o si maa gbadura fun un nigbagbogbo: lojojumọ ni a o si maa yin in. (Isa 60:6.)

16. Ìkúnwọ́ ọkà ni yoo maa wà lórí ilẹ̀, lori awọn òkè nla ni yoo maa mi eso rẹ̀ bi Lẹbanoni: ati awọn ti inu ilu yoo si ma gbá yìn bi koriko ilẹ̀. (Psm 104:16; Job 5:25.)

17. Orukọ rẹ̀ yoo wà titi lae, orukọ rẹ̀ yoo maa gbilẹ̀ niwọn bi òòrùn yoo ti pẹ́ tó: wọn o si maa bukun fun ara wọn nipasẹ rẹ̀: gbogbo awọn orilẹ-èdè ni yoo maa pe e ni alabukun-fún. (Psm 89:36; Gen 12:3; 22:18; Luk 1:48.)

**Oore-ọ̀fẹ́.**

18. Olubukun ni Oluwa Ọlọrun, Ọlọrun Israẹli, ẹnikanṣoṣo ti nṣe ohun iyanu.

19. Olubukun ni orukọ rẹ̀ ti o ni ògo títí lae: ki gbogbo ayé o si kun fun ogo rẹ̀; Amin, ati Amin! – (Neh 9:5; Sek 14:9.)

20. Adura Dafidi ọmọ Jesse pari.

## ÌWE KẸTA.

## ORIN 73.

**Jíjowú ẹni-ibi.**

NITOOTỌ Ọlọrun ṣeun fun Israẹli, fun irú awọn ti nṣe aláyà mímọ́. (Psm 86:5; 41:10.)

2. Ṣugbọn bi o ṣe temi ni, ẹsẹ̀ mi fẹ́rẹ̀ yẹ̀, irin mi fẹrẹ yọ́ tan. (Psm 94:18.)

3. Nitori ti emi ṣe ilara si awọn aṣefẹ́fẹ́, nigba ti mo ri alaafia awọn eniyan buburu. (Psm 37:1; Jer 12:1.)

**Ìlọsíwájú ẹni-ibi.**

4. Nitori ti kọ si irora ninu ikú wọn: agbara wọn si pọ̀.

5. Wọn kò ni ipin ninu iyọnu eniyan; bẹẹ ni a kò si wahala wọn bi i ti awọn ẹlomiran. (Job 21:9.)

6. Nitori naa ni igberaga ṣe ká wọn

lọrun bi ẹ̀wọ̀n ọ̀ṣọ́; iwa-ipá bò wọn mọlẹ bi aṣọ. (Psm 109:18.)

7. Oju wọn yọ jade fun ìṣanra: ọkàn wọn si kún àkúnwọsílẹ̀ ninu iwa were (omugọ). (Job 15:27; Psm 17:10.)

8. Wọn nṣẹ̀sín, wọn si nsọ̀rọ̀ buburu ni ti inilara: wọn nsọrọ lati ibi giga. (Psm 53:1; Jud 16.)

9. Wọn gbé ẹnu wọn lé ọ̀run, ahọ́n wọn si nrin ilẹ̀ já.

**Ẹkún olooto.**

10. Nitori naa ni awọn eniyan rẹ ṣe yipada si ihin: ọpọlọpọ omi ni a si npọn jade fun wọn.

11. Wọn si wi pe, "Ọlọrun ti ṣe mọ? Ìmọ̀ ha wà ninu ọgá-ogo? (Job 22:13.)

12. Kiyesi i, awọn wọnyìí ni alaiwa bi-Ọlọrun, ẹni ti ayé nsàn, wọn npọ̀ ni ọrọ̀. (Psm 49:6; Jer 49:31.)

13. Nitootọ ni asán ni mo wẹ àyà mi mọ́, ti mo si wẹ ọwọ́ mi ni ailẹṣẹ. (Job 21:15; 34:9; 35:3; Psm 2:6.)

14. Nitori pe ni gbogbo ọjọ́ ni a nyọ mi lẹnu, *a si nnà mi* ni òròwúrọ̀. (Psm 38:6; 118:18.)

**Títán iṣoro naa.**

15. Bi emi bá wi pé, "Emi o sọ bayìí:" kiyesi i, emi o ṣẹ sí ìran awọn ọmọ rẹ.

16. Nigba ti mo rò lati mọ̀ èyìí, o ṣòro loju mi. (Onws 8:17.)

17. Titi mo fi lọ sinu ibi-mímọ́ Ọlọrun; nigba naa ni mo mọ ìgbẹ̀hìn wọn; (Psm 77:13; 37:38.)

18. Nitootọ iwọ gbe wọn ka ibi yíyọ̀: iwọ tì wọ́n ṣubú sinu iparun. (Psm 35:6,8.)

19. Bawo ni a ti mu wọn lọ sinu idahoro yìí, bi ẹni pé ni iṣẹju kan! ibẹru ni a fi nrun wọn patapata. (Num 16:21; Job 18:11.)

20. Bi igba ti ẹnikan ba jí lójú àlá; bẹẹ ni Oluwa, nigba ti iwọ ba jí, iwọ o fi àbùkù kan aworan wọn. (Job 20:8; Psm 78:65; 1 Sam 2:30.)

**Idaniloju idande fun olooto.**

21. Bayìí ni inu mi bajẹ, ẹ̀gún si gun mi ni ọkàn mi.

22. Bẹẹ ni mo ṣiwere, ti emi kò sì mọ nkan; mo dabi ẹranko niwaju rẹ. (Psm 49:10; Job 18:3.)

23. Ṣugbọn emi wa pẹlu rẹ nigbagbogbo: iwọ ni o ti di ọwọ́ ọ̀tún mi mú.

24. Iwọ ọ fi ìmọ̀ rẹ tọ́ mi sí ọ̀nà, ati nígbẹ̀hìn iwọ o gba mi sinu ògo. (Psm 32:8; 48:14.)

25. Tani mo ni ní ọ̀run bikoṣe ìwọ? Kò si sí ohun ti mo fẹ ni ayé lẹhin rẹ. (Filp 3:8.)

26. Ẹran-ara mi ati àyà mi di àárẹ̀ tán; ṣugbọn Ọlọrun ni apata àyà mi, ati ìpín mi laelae. (Psm 84:2; 16:5.)

27. Sa wo o, awọn ti o jinna si ọ yoo ṣègbé: iwọ ti pa gbogbo wọn run ti nṣe àgbèrè kiri kúrò lọdọ rẹ. (Psm 37:20; 119:155.)

28. Ṣugbọn o dara fun mi lati sunmọ Ọlọrun: emi ti gbẹkẹ mí le Oluwa Ọlọrun, ki emi le maa sọ̀rọ̀ iṣẹ́ rẹ gbogbo. (Heb 10:22; Psm 71:7; 40:5.)

## ORIN 74.

**Ẹ̀bẹ̀ fun iranlọwọ.**

OLỌRUN, eeṣe ti iwọ fi ta wa nu titi lae! eeṣe ti ibinu rẹ fi nru si agutan papa rẹ? (Psm 44:9,23; Deut 29:20; Psm 95:7.)

2. Ranti ìjọ eniyan rẹ ti iwọ ti rà nigba àtijọ́; ilẹ-ìní rẹ ti ìwọ ti ra pada; òkè Sioni yìí, ninu èyí ti ìwọ ngbé. (Deut 32:6; Psm 77:15; 68:16.)

3. Gbe ẹsẹ̀ rẹ soke si ahoro laelae: àmí si gbogbo èyí ti ọ̀tá ti fi buburu ṣe ni ibi-mimọ. (Isa 61:2,7; Psm 79:1.)

4. Awọn ọ̀tá rẹ nke ramu-ramu laarin ijọ eniyan rẹ; wọn gbe asia wọn soke fun àmì. (E.Jer. 2:7; Num 2:2.)

5. Wọn dabi ọkunrin ti ngbe aaké rẹ̀ sókè ninu igbo dídí. (Jer 46:22.)

6. Ṣugbọn nisinsinyìí iṣẹ́ ọnà finfin ni wọn fi aaké òòlù wó lulẹ̀ pọ̀ ni ẹkan naa.

7. Wọn tiná bọ ibi-mimọ rẹ, ni wíwó ibùgbé orukọ rẹ lulẹ̀, wọn sọ ọ di eeri. (2 A.Ọba 25:9.)

8. Wọn wi ni ọkàn wọn pe, "Ẹ jẹ ki a run wọn pọ̀: wọn ti kun gbogbo ile Ọlọrun ni ilẹ naa. (Psm 83:4.)

9. Awa ko ri àmì wa: ko si woli kan mọ́: bẹẹ ni ko si ẹnikan ninu wa ti o mọ bi yoo ti pẹ tó. (Psm 78:43; 1 Sam 3:1; Psm 79:5.)

10. Ọlọrun, ọ̀tá yoo ti kẹ́gàn pẹ to? Ṣe ki ọ̀tá maa sọ̀rọ̀ òdì si orukọ rẹ laelae? (Psm 44:16; Lef 24:16.)

11. Eeṣe ti iwọ fi fa ọwọ́ rẹ sẹhin, ani ọwọ ọ̀tún rẹ? Fa a yọ jade kuro ni ookan àyà rẹ. (E.Jer. 2:3; Psm 59:13.)

**Idaniloju agbara Ọlọrun.**

12. Nitori Ọlọrun ni ọba mi ni atijọ wá ti nṣiṣẹ igbala laarin ayé. (Psm 44:4.)

13. Iwọ ni o ti ya òkun ni meji nipa agbara rẹ: iwọ ti fọ orí awọn erinmi ninu omi. (Eks 14:21; Isa 51:9.)

14. Iwọ fọ orí Lefiatani tuutu, o si fi i ṣe ounjẹ fun awọn ti ngbe inú ijù.

15. Iwọ là orisun ati ìṣàn-omi: iwọ gbé awọn odò nla. (Eks 17:5,6; Num 20:11; Jos 3:13.)

16. Tirẹ ni ọ̀sán, tìrẹ ni òru pẹ̀lú: iwọ ni o ti pèsè ìmọ́lẹ̀ ati òòrùn. (Psm 104:17.)

17. Ìwọ ni o ti pàlà eti ayé: iwọ ni o ṣe ìgbà ẹ̀rùn ati ìgbà òtútù. (Gen 8:22.)

**Ẹbẹ ikẹhin iranlọwọ.**

18. Ranti èyìí, Oluwa, pé ọ̀tá nkẹ́gàn, ati pé awọn eniyan buburu nsọrọ òdì sí orukọ rẹ. (ẹsẹ 10; Psm 39:8.)

19. Máṣe fi ọkàn àdàbà rẹ lé ẹranko igbẹ́ lọ́wọ́: máṣe gbàgbé ijọ awọn tálákà rẹ laelae. (O.Sol. 2:14; Psm 9:18.)

20. Júbà majẹmu rẹ: nitori ibi òkùnkùn ayé wọnyìí o kun fun ibugbe ìkà. (Gen 17:7; Psm 106:45; 88:10.)

21. Máṣe jẹ ki ẹni ti a ni lara pada ni ìtìjú; jẹ ki talaka ati alaini yin orukọ rẹ. (Psm 103:6; 35:10.)

22. Ọlọrun, dide, gbà ẹjọ ara rẹ rò: ranti bi aṣiwere (ọmùgọ̀) eniyan ti ngan ọ lojojumọ. (Psm 43:1; ẹsẹ 18.)

23. Máṣe gbàgbé ohùn awọn ọ̀tá rẹ: ìrọ́kẹ̀kẹ̀ awọn ti o dide si ọ npọ̀ si i nigbagbogbo. (ẹsẹ 10; Psm 65:7.)



## ORIN 75.

**Ìpè sí Ọlọrun.**

ỌLỌRUN, iwọ ni awa fi ọpẹ́ fun, iwọ ni awa fi ọpẹ fun nitori orukọ rẹ sunmọ tòsí, iṣẹ iyanu rẹ fi hàn. (Psm 79:13; 145:18; 44:1.)

**Ìdánilójú ìdájọ́.**

2. Nigba ti akoko mi ba dé, emi o fi otitọ ṣe idajọ.

3. Ayé ati gbogbo awọn ti ngbe inu rẹ wariri: emi ni o rù ọ̀wọ̀n rẹ. (Psm 46:6; 1 Sam 2:8.)

4. Emi wi fun awọn agbéraga pe, "Ẹ má ṣe gberaga mọ́:" ati fun awọn eniyan buburu pe, "Ẹ má ṣe gbe ìwo yin soke (Sek 1:21.)

5. Ẹ má ṣe gbe ìwo yin ga: ẹ má ṣe fi ọrùn lile sọrọ." (Psm 94:4.)

**Ọlọrun ni ōludajọ.**

6. Nitori ìgbẹ́lékè kò ti ìlà-oorùn wa, tabi ni ìwọ̀-oorun, bẹẹ ni ki i ṣe lati gusu wá. (Psm 3:3.)

7. Ṣugbọn Ọlọrun ni onidajọ: o sọ ọ̀kan kalẹ, o gbé ẹlomiran lékè. (Psm 50:6; 1 Sam 2:7; Dan 2:21.)

8. Nitori pé ni ọwọ́ Oluwa ni ago kan wà, ọtí-waini naa si pọ́n: ó kún fun àdàlú: o si dà jade ninu rẹ̀; ṣugbọn gẹ̀dẹ̀-gẹ́dẹ̀ rẹ̀, gbogbo awọn eniyan buburu ayé ni yoo fun ni afun-mu. (Job 21:20; Jer 25:15; Psm 60:3; Psm 73:10; Owe 23:30.)

**Ẹ yin Ọlọrun logo.**

9. Ṣugbọn emi o maa sọ títí lae, emi o maa kọrin ìyìn si Ọlọrun Jakọbu. (Psm 40:10.)

10. Gbogbo ìwo awọn eniyan buburu ni emi o ge kuro; ṣugbọn ìwo awọn olododo ni emi o gbé sókè. (Psm 89:17; 148:14.)

## ORIN 76.

**Agbara iṣẹgun Ọlọrun.**

NI Juda ni a gbe mọ Ọlọrun: orukọ rẹ̀ si pọ̀ ni Israẹli. (Psm 48:3.)

2. Ni Salemu pẹlu ni àgọ́ rẹ̀ wà, ati ibùgbé rẹ̀ ni Sioni. (Psm 27:5; 9:11.)

3. Nibẹ ni o gbe ṣẹ́ ọfà, ọ̀rún apata, ati idà, ati ogun naa. (Psm 46:9.)

4. Iwọ ní ògo ati ọlá jù òkè-nla ikogun wọnyìí lọ.

5. A kó awọn aláyà líle ni ikogun, wọn ti sun orun wọn, gbogbo ọkunrin alagbara kọ si ri ọwọ́ wọn. (Isa 46:12; Psm 13:3.)

6. Nipa ibawi rẹ, Ọlọrun Jakọbu, ati kẹkẹ-ogun ati ẹṣin sun orun àsùnkú. (Eks 15:1,21; Psm 78:53.)

7. Iwọ, ani iwọ ni o ni ìbẹ̀rù ati tani yoo le dúró niwaju rẹ, nigba ti iwọ ba binu lẹẹkan? (Psm 96:4; Nah 1:6.)

8. Iwọ mu idajọ di gbígbọ́ lati ọrun wá: ile ayé bẹru o si duro jẹ́. (Eks 38:20; 2 Kro 20:29.)

9. Nigba ti Ọlọrun dide si idajọ, lati gba gbogbo ọlọkan-tutu ayé là. (Psm 9:7–9; 72:4.)

10. Nitootọ ibinu eniyan yoo yin ọ: nigba ti iwọ ba fi ibinu ìyókù di ara rẹ ni àmùrè. (Eks 9:16; Rom 9:17.)

11. Ẹ ṣe ileri ìfẹ́, ki ẹ si san an fun Oluwa, Ọlọrun yin: jẹ ki gbogbo awọn ti o yii ka mu ẹ̀bùn wa fun ẹni ti o yẹ lati bẹru. (Psm 50:14; 68:29.)

12. Ẹni ti o ge ẹ̀mí awọn ọmọ alade kúrò: oun si di ẹ̀rù sí awọn ọba ayé.

## ORIN 77.

**Ìpè fun iranlọwọ.**

EMI fi ohùn kigbe si Ọlọrun, àní si Ọlọrun ni mo fi ohùn mi ké pè: ó si fi etí si mi. (Psm 3:4.)

2. Ni ọjọ iponju mi emi ṣe afẹri Ọlọrun: ọwọ́ mi nnà ni òru, kò si rẹ̀ silẹ: ọkàn mi kọ̀ ati tù ninu. (Psm 50:15; Isa 26:9,16.)

3. Ẹmi ranti Ọlọrun, emi kẹ́dùn: emi ṣe àròyé, ẹmi mi si rẹ̀wẹ̀si. (Psm 142:3; 143:4.)

4. Iwọ ko fẹ ki emi fi ojú ba oorun: ẹnu yà mi tobẹẹ ti emi kò le sọ̀rọ̀.

5. Emi ti nrò ọjọ́ àtijọ́, ọdún ìgbàani. (Deut 32:7; Psm 143:5; Isa 51:9.)

6. Mo ranti orin mi ni òru: emi nba àyà mi sọ̀rọ̀: ọkàn mi si nṣe àwárí jọjọ. (Psm 74:8; 4:4.)

7. Oluwa yoo ha ṣá ni tì laelae? Ki yoo ha ṣe ojú rere mọ́ bí? (Psm 74:1; 85:1.)

8. Aanu rẹ ha lọ laelae? Ileri rẹ ha yẹ titi láe? (Psm 89:49; 2 Pet 3:9.)

9. Ọlọrun ha gbagbe lati ṣe oju rere ninu ibinu rẹ̀ o ha sé ironu aanu rẹ̀ mọ́?" (Isa 49:15; Psm 25:6.)

10. Emi wi pe, "Eyi ni ẹdùn-ọkan mi pe ọwọ ọ̀tún Ọga-Ogo ti yípadà." (Psm 31:22; 44:2,3.)

**Iṣẹ́ iyanu ti Ọlọrun ti ṣe.**

11. Emi o ranti iṣẹ́ Oluwa: nitootọ emi o ranti iṣẹ iyanu rẹ àtijọ́. (Psm 143:5.)

12. Ṣugbọn emi o maa ṣe àṣàrò gbogbo iṣẹ rẹ pẹlu, emi o si maa sọ̀rọ̀ iṣẹ́ rẹ.

13. Ọ̀nà rẹ Ọlọrun, mímọ́ ni, tani alagbara ti o tobi bi Ọlọrun? (Psm 73:17; Eks 15:11.)

14. Iwọ ni Alagbara ti nṣe iyanu: iwọ ni o ti fi ipa rẹ hàn ninu awọn eniyan.

15. Iwọ ni o ti fi apá rẹ rà awọn eniyan rẹ pada, awọn ọmọ Jakọbu ati Josẹfu. (Eks 6:6; Deut 9:29.)

16. Nigba ti awọn omi ri ọ, Ọlọrun, nigba ti awọn omi ri ọ, ẹ̀rù ba wọn: nitootọ ara ibú kò balẹ̀. (Eks 14:21.)

17. Awọsanma da omi silẹ̀: ojusanma rán iró jade: ọfà rẹ jade lọ pẹlu. (Ondj 5:4; Psm 68:33; 2 Sam 22:15.)

18. Ohùn àárá rẹ nsán ni ọrun: manamana nkọ si ayé, ilẹ̀ wá-rìrì, ó sì mì. (2 Sam 22:8.)

19. Ọ̀nà rẹ nbẹ ni òkun, ati ipa rẹ ninu awọn omi nla, ipasẹ rẹ ni a kò si mọ̀. (Hab 3:15; Eks 14:28.)

20. Iwọ da awọn eniyan rẹ bi ọ̀wọ́-ẹran nipa ọwọ́ Mose ati Aaroni. (Eks 13:21; Isa 63:11–13; Eks 6:26.)

## ORIN 78.

**Ìpè lati gbọ́ ati lati gbà.**

FI etí sílẹ̀, ẹ̀yin ẹniyan mi, dẹ etí yin silẹ si ọ̀rọ̀ ẹnu mi. (Isa 51:4.)
2. Emi o ya ẹnu mi lowe: emi o sọ ọ̀rọ̀ àtijọ́ ti o ṣokunkun jade; (Matt 13:35.)
3. Ti awa ti gbọ́, ti a si ti mọ̀, ti awọn baba wa si ti sọ fun wa. (Psm 44:1.)
4. Awa ki yoo pa wọn mọ́ kuro lọdọ awọn ọmọ wọn, ni fifi ìyìn Oluwa, ati ipa rẹ̀, ati iṣẹ́ iyanu ti o ti ṣe hàn fun ìran ti nbọ. (Eks 12:26; Psm 22:30; 71:17.)
5. Nitori ti o gbé ẹ̀rí kalẹ ni Jakọbu, o si sọ òfin kan ni Israẹli, ti o pa ni àṣẹ fun awọn baba wa pe ki wọn lè sọ wọn di mímọ̀ fun awọn ọmọ wọn. (Psm 147:19; Deut 4:9.)
6. Ki awọn ìran ti nbọ le mọ̀, àní awọn ọmọ ti a o bi: ti yoo si dide, ti yoo si sọ fun awọn ọmọ wọn. (Psm 102:18.)
7. Ki wọn lẹ maa gbe ireti wọn le Ọlọrun, ki wọn má si ṣe gbàgbé iṣẹ́ Ọlọrun, ṣugbọn ki wọn maa pa ọfin rẹ̀ mọ́. (Deut 6:12; 27:1.)
8. Ki wọn ma ṣe dabi awọn baba wọn, ìran agídí ati ọlọ̀tẹ̀; ìran ti kọ fi ọkàn wọn lẹ otitọ, ati ẹmi ẹni ti ko ba Ọlọrun duro ṣinṣin. (Esk 20:18; Eks 32:9; ẹsẹ 37.)

**Aigbọran Efraimu.**

9. Awọn ọmọ Efraimu ti o hamọra ogun, ti wọn mú ọrun, wọn yipada ni ọjọ́ ogun. (1 Kro 12:2; Ondj 20:39.)
10. Wọn ko pa majẹmu Ọlọrun mọ; wọn si kọ̀ lati maa rin ninu òfin rẹ̀. (2 A.Ọba 18:12; Psm 119:1.)
11. Wọn si gbagbe iṣẹ́ rẹ̀, ati ohun iyanu rẹ̀, ti o ti fi hàn wọ́n. (Psm 106:13.)
12. Ohun iyanu ti o ṣe niwaju awọn baba wọn ni ilẹ Egipti, ani ni igbẹ Soani. (Eks ori 7–12; Num 13:22; Isa 19:11,13; Eks 30:14.)
13. Ópín òkun níyà, o si mu wọn la a ja; o si mu omi duro bi bèbè. (Eks 14:21; 15:8.)
14. Ni ọsan pẹlu o fi ìkúùkuu awọsanma ṣe amọna wọn, ati loru gbogbo pẹlu imọle iná. (Eks 13:21.)
15. O sán apata ni aginjù, o si fun wọn ni omi mimu lọpọlọpọ bi ẹni pe lati inu ibú wá. (Num 20:11; 1 Kro 10:4.)
16. O si mu ìṣàn-omi jade wá lati inu apata, o si mu omi ṣàn silẹ bi odò.

**Ìbéèrè ifẹkufẹ fun ẹran jijẹ.**

17. Wọn si tún ṣẹ̀ si i; ni ṣíṣọ̀tẹ̀ si Ọgá-ògo ni aginju. (Deut 9:22; Heb 3:16.)
18. Wọn si dán Ọlọrun wò ni ọkàn wọn, ni bibeere ounjẹ fun ifẹkufẹ wọn. (Eks 16:2; 1 Kro 10:9.)
19. Wọn si sọrọ si Ọlọrun; wọn wi pe, "Ọlọrun ha le tẹ tabili ni aginju?" (Num 11:4.)
20. Wo o! o lu apata, omi si tú jade, ìṣàn-omi si kún pupọ; o ha le funni ni àkàrà pẹlu? O ha le pèsè ẹran fun awọn eniyan rẹ̀?" (Num 20:11.)
21. Nitori naa, Oluwa gbọ́ eyìí, ò binu: bẹẹ ni iná ran ni Jakọbu, ibinu si rú ni Israeli. (Num 11:1.)
22. Nitori ti wọn kò gba Ọlọrun gbọ́, wọn kò si gbẹkẹle igbala rẹ̀. (Heb 3:18.)
23. Ó pàṣẹ fun awọsanma lati oke wá, o si ṣi ilẹkun ọrun sílẹ̀. (Mal 3:10.)
24. O si rọ̀jò Manna silẹ fun wọn ni jijẹ, o si fun wọn ni ọkà ọrun. (Jhn 6:31.)
25. Eniyan jẹ ounjẹ awọn angẹli; o ran ounjẹ si wọn ni ajẹyo.
26. O mu afẹ́fẹ́ ìlà-oòrùn fẹ ni ọrun, ati nipa agbara rẹ̀ o mu afẹfẹ gusu wá. (Num 11:31.)
27. Ó rọ̀jò ẹran si wọn pẹ̀lú bi erùpẹ̀ ilẹ̀, ati ẹyẹ abìyẹ́ bi iyanrin òkun. (Psm 105:40.)
28. O si jẹ ki wọn ọ bọ́ si aarin ibùdó wọn, yi àgọ́ wọn ká.
29. Bẹẹ ni wọn jẹ, wọn si yo jọjọ: nitori ti o fi ìfẹ́ wọn fun wọn. (Num 11:20.)

30. Wọn ko kuro ninu ifẹkufẹ wọn; nigba ti ounjẹ wọn si wa ni ẹnu wọn.

31. Ibinu Ọlọrun dé si ori wọn, o pa awọn ti o sanra ninu wọn, o si lu awọn ọdọmọkunrin Israẹli bolẹ. (Num 11:33.)

32. Ninu gbogbo wọnyii wọn nṣẹ siwaju, wọn ko si gbà iṣẹ iyanu rẹ gbọ́. (Num 14:16,17; ẹsẹ 22.)

33. Nitori naa ni o ṣe sọ ọjọ́ wọn ni asán, ati ọdún wọn ni ìjáyà. (Num 14:29,35.)

34. Nigba ti o pa wọn, nigba naa ni wọn wá a kiri: wọn si pada, wọn bèèrè Ọlọrun lakoko. (Hos 5:15.)

35. Wọn si ranti pe, Ọlọrun ni apata wọn, ati Ọlọrun Ọ̀gá-ògo ni Oludande wọn. (Deut 32:4; Isa 41:14.)

36. Ṣugbọn ẹnu wọn ni wọn fi pọ́n ọn, wọn si fi ahọ́n wọn ṣeke si i. (Esk 33:31; Eks 32:7,8.)

37. Nitori ọkàn wọn ko ṣe deede pẹlu rẹ̀, bẹẹ ni wọn kò si duro ṣinṣin ni majẹmu rẹ̀.

38. Ṣugbọn oun, o kun fun ìyọ́nú, o fi ẹ̀ṣẹ̀ wọn ji wọn, kò si run wọn: nitootọ, nigba pupọ ni o yí ibinu rẹ̀ padà, ti kò si ru gbogbo ibinu rẹ sókè. (Num 14:18; Isa 48:9; 1 A.Ọba 21:29.)

39. Nitori ti o ranti pé, eniyan saa ni wọn; afẹ́fẹ́ ti nkọja lọ, ti kò si tun pada wá mọ́. (Psm 103:14; Heb 3:16.)

**Israẹli gbagbe aanu Ọlọrun.**

40. Ìgbà melo-melo ni wọn ṣọ̀tẹ̀ si i ni aginju, ti wọn si ba a ninu jẹ́ ni aṣálẹ̀! (Psm 95:8–10; Heb 3:16.)

41. Nitootọ, wọn yipada, wọn si dan Ọlọrun wò, wọn si ṣe àròpin Eni-Mímọ́ Israẹli. (Num 14:22; Psm 89:18.)

42. Wọn ko ranti agbara rẹ̀, tabi ọjọ́ ti o gba wọn lọwọ ọ̀tá.

43. Bi o ti ṣe iṣẹ́-àmì rẹ̀ ni Egipti, ati iṣẹ́ iyanu rẹ̀ ni ìgbẹ́ Soani.

44. Ti o si sọ odò wọn di ẹ̀jẹ̀; ati omi ṣíṣàn wọn, ti wọn kò fi le mu un. (Eks 7:20.)

45. O rán eṣinṣin sinu wọn, tí ó jẹ wọ́n; ati ọ̀pọ̀lọ̀ ti o run wọn. (Esk 8:24; Psm 105:31; Eks 8:6.)

46. O fi èso ilẹ̀ wọn fún kòkòrọ̀ pẹlu; ati iṣẹ́ wọn fún eeṣú.

47. O fi yìnyín pa àjàrà wọn, o si fi yìnyín nla pa igi sikamore wọn. (Eks 9:25.)

48. O fi ohun ọ̀sìn wọn pẹlu fun yìnyín, ati agbo-ẹran wọn fun manamana. (Eks 9:23.)

49. O mu kikoro ibinu rẹ̀ wa si wọn lara, ìrunú ati ìkannú, ati ipọnju, nipa rírán angẹli ibi sinu wọn. (Eks 15:7.)

50. Ó ṣínà silẹ fun ibinu rẹ̀; kò da ọkàn wọn si lọwọ́ ikú, ṣugbọn o fi ẹmi wọn fun àjakalẹ-àrùn.

51. O si kọlu gbogbo awọn akọbi ni Egipti, olori agbara wọn ninu àgọ́ Hamu: (Eks 12:29; Psm 106:22.)

52. Ṣugbọn o mu awọn eniyan tirẹ̀ lọ bi agutan, o si ṣe itọju wọn ni ijù bi agbo-ẹran. (Psm 77:20.)

53. O si ṣe amọna wọn ni alaafia, bẹẹ ni wọn ko si bẹru: ṣugbọn òkun bo awọn ọta wọn mọlẹ. (Eks 14:19,27.)

54. O si mu wọn wa si eti ibi-mímọ́ rẹ, ani si oke yii ti ọwọ ọtun rẹ ti ra. (Eks 15:17; Psm 44:3.)

55. O ti awọn Keferi jade pẹlu kuro niwaju wọn, o si fi tita okùn pínlẹ̀ fun wọn ni ilẹ-ìní, o si mu awọn ẹ̀yà Israẹli jókòó ninu àgọ́ wọn. (Psm 44:2; 106:11.)

**Iwa iborisa Israeli ni ilẹ̀ Kenaani.**

56. Ṣugbọn wọn dan an wò, wọn si ṣọ̀tẹ̀ si Ọlọrun Ọ̀gá-ògo, wọn ko si pa ẹ̀rí rẹ̀ mọ́. (ẹsẹ 18,40.)

57. Ṣugbọn wọn yipada, wọn ṣe alaiṣotitọ bi awọn baba wọn: wọn si pẹhinda si apakan bi ọrun ẹ̀tàn. (Eks 20:27,28; Hos 7:16.)

58. Nitori ti wọn fi ibi giga wọn bi i ninu, wọn si fi ère fínfín wọn mu un jowú. (Deut 32:16,21; 12:2; 1 A.Ọba 11:7.)

59. Nigba ti Ọlọrun gbọ́ èyíí, ó bínú, o si korira Israẹli gidigidi.

60. Bẹẹ ni ó kọ̀ àgọ́ ṣilo silẹ, àgọ́ ti o pa laarin awọn eniyan. (1 Sam 4:11.)

61. O si fi agbara rẹ̀ fun ìgbèkùn, ati ògo rẹ̀ lé ọwọ́ ọtá. (Ondj 18:30.)

62. O fi awọn eniyan rẹ̀ fun idà pẹlu; o si binu si ilẹ-ini rẹ̀. (1 Sam 4:10.)

63. Iná run awọn ọdọmọkunrin wọn; a ko si fi orin sin awọn wundia wọn ni iyawo. (Jer 7:34.)

64. Awọn alufa wọn ti ojú idà ṣubú; awọn opó wọn kò si pohunrere ẹkún. (1 Sam 22:18; Job 27:15.)

65. Nigba naa ni Oluwa jí bi ẹni pé loju oorun, ati bi alagbara ti nkígbe nitori ọti-waini. (Isa 42:13.)

66. O si kọlu awọn ọtá rẹ̀ lẹhin; o sọ wọn di ẹ̀gàn títí ayé. (1 Sam 5:6.)

**Juda ati Dafidi àyànfẹ́.**

67. Pẹlupẹlu o kọ àgọ́ Josẹfu, kò si yan ẹ̀yà Efraimu:

68. Ṣugbọn o yan ẹ̀yà Juda, òkè Sioni ti o fẹ́. (Psm 87:2.)

69. O si kọ́ ibi-mímọ́ rẹ̀ bi òkè-ọrun bi ilẹ ti o fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ laelae. (1 Sam 6:1–38.)

70. O si yàn Dafidi iranṣẹ rẹ̀, o si mu un kuro lati inu agbo-agutan wá: (1 Sam 16:11,12.)

71. Lati máa tọ awọn agutan lẹhin, ti ọ tobi fun oyún, o mu un lati maa jẹ́ oluṣọ-agutan Jakọbu, eniyan rẹ̀, ati Israẹli, ilẹ-ini rẹ̀. (2 Sam 7:8; Gen 33:13; 1 Kro 11:2.)

72. Bẹẹ ni o bọ́ wọn gẹgẹ bi ìwà òótọ́ inu rẹ̀: o si fi ọgbọ́n ọwọ́ rẹ̀ ṣe amọ̀nà wọn. (1 A.Ọba 9:4.)

## ORIN 79.

**Ìwà ipa ati ẹ̀ṣẹ̀ ni Jerusalẹmu.**

OLORUN, awọn Keferi wa si ilẹ-ìní rẹ; tempili mímọ́ rẹ ni wọn sọ di ẹ̀érí: wọn sọ Jerusalẹmu di okiti-àlàpà. (Eks 15:17; Psm 74:2; 2 A. Ọba 25:9; Mika 3:12.)

2. Okú awọn iranṣẹ rẹ ni wọn fi fun ẹyẹ oju-ọrun ni ounjẹ, ẹran-ara awọn eniyan mímọ́ rẹ fun ẹranko ilẹ̀. (Jer 7:33.)

3. Wọn ta ẹ̀jẹ̀ wọn silẹ bi omi yi Jerusalẹmu ká; kò si sí ẹni ti yoo gbe wọn sin. (Jer 14:16.)

4. Awa di ẹ̀gàn si awọn aladugbo wa, ẹlẹya ati iyọṣùtì si awọn ti o yi wa ká. (Psm 44:13.)

**Ẹ̀bẹ̀ fún ìrànlọ́wọ́ Oluwa.**

5. Yoo ti pẹ tó, Oluwa? Iwọ o binu titi laelae? Owú rẹ yoo ha maa jó bi iná? (Psm 74:1–9; Sef 3:8.)

6. Da ibinu rẹ si orí awọn Keferi ti ko mọ ọ, ati si ori awọn ijọba ti ko ke pe orukọ rẹ. (Jer 10:25; Ifh 16:1; Isa 45:4,5; 2 Tess 1:8.)

7. Nitori ti wọn ti mu Jakọbu jẹ, wọn si sọ ibùgbé rẹ̀ di ahoro.

8. Má ṣe ranti ẹ̀ṣẹ̀ awọn aṣaaju wa sí wa: jẹ ki iyọ́nú rẹ ṣaaju wa nisinsinyii: nitori ti a rẹ̀ wa silẹ gidigidi. (Isa 64:9.)

9. Ràn wa lọwọ, Ọlọrun igbala wa, nitori ogo orukọ rẹ: gbà wá, ki o si wẹ ẹ̀ṣẹ̀ wa nù, nitori orukọ rẹ. (2 Kro 14:11; Jer 14:7.)

10. Nitori kinni awọn Keferi yoo ṣe wi pe, Nibo ni Ọlọrun wọn wa? Jẹ ki a mọ ìgbẹ̀san ẹ̀jẹ̀ awọn iranṣẹ rẹ ti a ta silẹ loju wa ninu awọn Keferi. (Psm 42:10; 94:1,2.)

11. Jẹ ki imí-ẹ̀dùn onde naa wá siwaju rẹ: gẹgẹ bi titobi agbara rẹ, iwọ da awọn ti a yàn si pípa sílẹ̀. (Psm 102:20.)

12. San ẹ̀gàn wọn nigba meje fun awọn aladugbo wa ni àyà wọn, nipa ẹ̀yí ti wọn ngan ọ, Oluwa. (Isa 65:6,7; Jer 32:18; Luk 6:38; Psm 74:18; Psm 74:18–22.)

13. Bẹẹ ni awa eniyan rẹ ati agutan pápá rẹ, yoo maa fi ọpẹ́ fun ọ laelae awa o maa fi iyìn rẹ hàn lati irandiran. (Psm 74:1; 75:7; Isa 43:21.)

## ORIN 80.

**Ìpè fún iranlọwọ.**

FI etí sílẹ̀, Oluṣọ-agutan Israẹli, iwọ ti o ndà Josẹfu bi ọ̀wọ́-agutan; iwọ ti o jókòó laarin awọn kérúbù tàn imọlẹ jade. (Psm 23:1; 77:20; 99:1.)

2. Niwaju Efraimu ati Bẹnjamini ati Manasse rú ipa rẹ soke ki o si wá fun igbala wa. (Psm 35:23.)

3. Tún wa yipada, Ọlọrun, si mu ojú rẹ tàn imọlẹ; a o si gbà wa là. (E.Jer. 5:21; Num 6:25.)

**Ìsòro Israẹli.**

4. Oluwa awọn ọmọ-ogun, iwọ o ti binu pẹ to si adura awọn eniyan rẹ? (Psm 85:5.)

5. Iwọ fi ounjẹ omije bọ wọn; iwọ sí fun wọn ni omije mu lọpọlọpọ. (Psm 42:3; 102:9.)

6. Iwọ sọ wa di ẹlẹ́yà fun awọn aladugbo wa: awọn ọtá wa si nrẹrin ninu ara wọn. (Psm 44:13; 79:4.)

7. Tún wa yipada, Ọlọrun awọn ọmọ-ogun, si mu ojú rẹ tan imọlẹ; a o si gbà wa là.

**Àjàrà ti ko wúlò ni Israẹli.**

8. Iwọ ti mu ajara kan ti Egipti wa: iwọ ti ti awọn Keferi jade, iwọ si gbin in. (Isa 5:1–7; Jer 2:21; Esk 15:6; Psm 44:2.)

9. Iwọ ṣi àyè sílẹ̀ fun un, iwọ si mu un ta gbòngbò jinlẹ, o si kun ilẹ naa. (Hos 14:5.)

10. A fi ojiji rẹ bo awọn òkè mọ́lẹ̀, ati ẹka rẹ̀ dabi igi Kedari Ọlọrun.

11. Ó yọ ẹ̀ka rẹ sinu òkun, ati ọwọ́ rẹ̀ si odò nla ni.

12. Eeṣe ti iwọ fi wó ọgbà rẹ̀ lulẹ̀ bẹẹ, ti gbogbo awọn ẹni ti nkọja lọ ni ọ̀nà nka eso rẹ̀? (Psm 89:40; Nah 2:2.)

13. Ìmàdò lati inu igbó wa nba a jẹ, ati ẹranko ìgbẹ́ njẹ ẹ run. (Jer 5:6.)

**Àtúnwí ìpè fun iranlọwọ.**

14. Yipada, awa nbẹ ọ, Ọlọrun awọn ọmọ-ogun: wolẹ̀ lati ọrun wá, wo o, ki o si bẹ àjàrà yìí wo. (Isa 63:15.)

15. Ati àgbàlá-ajara ti ọwọ́ ọtun rẹ ti gbìn, ati ọmọ ti iwọ ti múle fun ara rẹ.

16. Ó jóná, a ge e lulẹ: wọn ṣegbe nipa ibawi oju rẹ. (Psm 39:11; 76:6.)

17. Jẹ ki ọwọ́ rẹ o wà lara ọkunrin ọwọ́ ọ̀tún rẹ, lara ọmọ-eniyan ti iwọ ti múle fun ara rẹ. (Psm 89:21.)

18. Bẹẹ ni awa ki yoo pada sẹhin kuro lọdọ rẹ: mu wa yè, awa o si maa pè orukọ rẹ. (Isa 50:5; Psm 71:20.)

19. Tún wa yipada, Oluwa Ọlọrun awọn ọmọ-ogun, mu ojú rẹ tàn imọ́lẹ̀; a o si gbà wa là.

ORIN 81.

**Ìpè lati yin Ọlọrun.**

KỌRIN soke si Ọlọrun, ipá wa: ẹ ho ìhó ayọ̀ si Ọlọrun Jakọbu. (Psm 59:16; 66:1.)

2. Ẹ mu orin mímọ́, ki ẹ si mu ìlù wa, dùùrù didun pẹlu ohun-èlò orin mímọ́.

3. Ẹ fun ìpè ni oṣù tuntun, ni ìgbà ti a lànà sílẹ̀, ni ọjọ́ àjọ wa ti o ni ìrònú. (Num 10:10; Lef 23:24.)

4. Nitori èyí ni àṣẹ fun Israẹli, ati òfin Ọlọrun Jakọbu.

5. Èyí ni o dasilẹ ni Josẹfu fún ẹ̀rí, nigba ti o la ilẹ Egipti já; nibi ti mo gbé gbọ́ èdè ti kò ye mi. (Eks 11:4.)

**Ìfẹ́ Ọlọrun si Israẹli.**

6. Mo gbé ejika rẹ̀ kuro ninu ẹrù: mo si gba agbọ̀n lọwọ rẹ̀. (Isa 9:4; 10:27.)

7. Iwọ pè ninu ipọnjù, emi si gbà ọ́; emi da ọ lóhùn nibi ìkọ̀kọ̀ àárá: emi ridi rẹ nibi omi ìjà. (Eks 2:23; Psm 50:15; Eks 19:19; 17:6,7.)

8. Ẹ gbọ́, ẹ̀yin eniyan mi, níwọ̀n bi mo ti nkilọ fun yin: Israẹli, bi iwọ ba le fetisi mi! (Psm 50:7.)

9. Ki yoo si ọlọrun miran ninu yin; bẹẹ ni iwọ ki yoo sin ọlọrun àjèjì. (Deut 32:12; Isa 43:12.)

10. Emi ni Oluwa Ọlọrun rẹ, ti o mu ọ lati ilẹ Egipti jade wa: ya ẹnu rẹ gbòrò, emi o si kún un. (Eks 20:2; Psm 103:5.)

**Ọlọrun npe apẹhinda Israẹli.**

11. Ṣugbọn awọn eniyan mi ko fẹ gbọ ohùn mi; Israẹli ko si fẹ tèmi. (Eks 32:1.)

12. Bẹẹ ni mo fi wọn silẹ fun lile àyà wọn: wọn si nrin ninu èrò ara wọn. (A.A. 7:42; Rom 1:24.)
13. Ibaṣe pe awọn eniyan mi ti gbó temi, ati ki Israẹli maa rin nipa ònà mi! (Deut 5:29; Isa 48:18; Psm 128:1.)
14. Emi iba ti ṣẹ́ awọn ọ̀tá wọn lógán, emi iba si ti yi ọwọ́ mi pada si awọn ọ̀tá wọn. (Psm 47:3; Amos 1:8.)
15. Awọn akorira Oluwa iba ti fi ori wọn balẹ fun un; ìgbà wọn iba si duro pẹ titi.
16. "Alikama daradara ni emi iba maa fi bọ́ yin pẹlu: ati oyin inu apata ni emi iba si maa fi tẹ ọ lọrun." (Deut 32:13; Psm 147:14.)

## ORIN 82.

**Idajọ àìtọ́ ni a bawi.**

OLỌRUN duro ninu ijọ awọn alagbara; o nṣe idajọ laarin awọn ọlọrun. (Isa 3:13; Eks 21:6.)
2. Ẹyin o ti ṣe idajọ aiṣootọ pẹ to, ti ẹ o si maa ṣe ojuṣaju awọn eniyan buburu? (Psm 58:1; Deut 1:17; Owe 18:5.)
3. Ṣe idajọ talaka, ati ti alaini-baba ṣe otitọ si awọn olupọnju ati alaini. (Deut 24:17.)
4. Gbà talaka ati alaini: yọ wọn ni ọwọ́ awọn eniyan buburu." (Job 29: 12.)
5. Wọn kò mọ, bẹẹ ni wọn ko fẹ ki òye ye wọn; wọn nrin ni okunkun; gbogbo ipilẹ ayé yẹ̀ ni ipò wọn. (Mika 3:1; Psm 11:3.)
6. Emi ti wi pe, ọlọrun ni ẹ̀yin, awọn ọmọ Ọga-ogo si ni gbogbo yín. (Jhn 10:34; Psm 89:26.)
7. "Ṣugbọn ẹ̀yin o ku bi eniyan, ẹ̀yin o si ṣubú bi ọ̀kan ninu awọn ọmọ-aladẹ." (Psm 49:12; Esk 31:14.)
8. Ọlọrun, dide, ṣe idajọ ayé: nitori iwọ ni yoo ni orilẹ-ède gbogbo. (Psm 12:5; Mika 7:2–7; Psm 2:8; Ifh 11:15.)

## ORIN 83.

**Adura lati bá ọ̀tá Israẹli wí.**

MÁ ṣe dákẹ́, Ọlọrun: ma ṣe pa ẹnu rẹ mọ́, má si ṣe duro jẹ, Ọlọrun. (Psm 28:1; 109:1.)
2. Sa wò o, awọn ọ̀tá rẹ nrọ́kẹ̀kẹ̀: awọn ti o korira rẹ ti gbé orí soke. (Psm 1:1; 81:15.)
3. Wọn ti gbìmọ̀ arekereke si awọn eniyan rẹ, wọn si ti gbìrò si awọn ẹni-ìkọ̀kọ̀ rẹ. (Psm 27:5.)
4. Wọn ti wi pe, "Ẹ wá, ẹ jẹ ki a ge wọn kuro lati má wà ni orilẹ-ede; ki orukọ Israẹli máṣe si ni iranti mọ́. (Est 3:6.)
5. Nitori ti wọn ti gbìmọ̀ pọ̀ ṣọ̀kan; wọn ti dimọlu si ọ. (Psm 2:2.)
6. Agọ Edomu, ati ti awọn ọmọ Iṣmaẹli; ti Moabu, ati awọn ọmọ Hagari. (2 Kro 20:1; 10:11.)
7. Gebali, ati Ammoni, ati Amaleki; awọn ará Filistini pẹlu awọn ara Tire.
8. Assuri pẹlu dàpọ̀ mọ wọn: wọn rán awọn ọmọ Lotu lọ́wọ́.

**Adura lati san ẹ̀san fún awọn ọ̀tá.**

9. Ṣe wọn bi o ti ṣe awọn ara Midiani; bi Sisera, bi Jabini, ni odò Kisoni. (Ondj 4:12–21.)
10. Ẹni ti o ṣègbé ni Endori: wọn di àtàn fún ilẹ̀.
11. Ṣe awọn ọlọla wọn bi Orebu ati bi Sebu: ani, gbogbo awọn ọmọ-alade wọn bi Seba ati Salmuna. (Ondj 8:12–21.)
12. Awọn ti o wi pe, "Ẹ jẹ ki a gbà ibugbe Ọlọrun wọnyii fun ara wa ni ini." (2 Kro 20:11; Psm 132:13.)
13. Ọlọrun mi, ṣe wọn bi ààjà; bi àgékù koriko niwaju afẹ́fẹ́. (Isa 17:13; Psm 35:5.)
14. Bi iná ti njó igbó, ati bi ọwọ́ iná ti nmu òkè-nla gbiná. (Deut 32:22.)
15. Bẹẹ ni ki o fi ẹfúùfù rẹ ṣe inunibini si wọn, ki o si fi ìjì rẹ dẹruba wọn. (Job 9:17.)
16. Fi ìtìjú kun wọn loju: ki wọn o le maa ṣe àfẹ́rí orukọ rẹ, Oluwa.

17. Ki wọn daamu ki a si pọ́n wọn loju laelae nitootọ́, ki a dojuti wọn, ki wọn ṣègbé. (Psm 70:2.)
18. Ki awọn eniyan lẹ mọ pe iwọ, orukọ ẹni-kanṣoṣo ti nje JEHOFA, iwọ ni Ọgá-ògo lori ayé gbogbo. (Psm 59:13; Eks 6:3; Psm 92:8.)

ORIN 84.

**Ìfẹ́ si àgbàlá Ọlọrun.**

AGỌ ibùgbé rẹ ti ni ẹwà to, Oluwa awọn ọmọ-ogun! (Psm 27:4.)
2. Ọkàn mi nfa nitootọ, o tilẹ poungbẹ fun àgbàlá Oluwa; àyà mi ati ara mi nkigbe si Ọlọrun alàààyè. (Psm 42:1,2.)

**Ibukun ni fun awọn ti ngbe ile Oluwa.**

3. Nitootọ, ologoṣẹ ri ile, ati alapandẹdẹ tẹ itẹ fun ara rẹ, nibi ti yoo gbe maa pa awọn ọmọ rẹ mọ si, àní nibi awọn pẹpẹ rẹ, Oluwa awọn ọmọ-ogun, Ọba ati Ọlọrun mi. (Psm 43:4; 5:2.)
4. Ibukun ni fun awọn ti ngbe inu ile rẹ: wọn o maa yin ọ sibẹ. (Psm 65:4.)

**Ibukun ni fun ẹni ti o nwa ile Ọlọrun.**

5. Ibukun ni fun eniyan naa, ipá ẹni ti o wà ninu rẹ: ni ọkàn ẹni ti ọ̀nà rẹ wà. (Psm 81:1.)
6. Awọn ti nla afonifoji omijé lọ, wọn sọ ọ di kònga; àkọ́rọ̀-òjò si fi ibukun bò o. (2 Sam 5:23; Psm 107:35.)
7. Wọ́n nlọ lati ipá dé ipa, ni Sioni ni wọ́n yọ niwaju Ọlọrun. (Owe 4:18; 2 Kro 3:18; Deut 16:16.)

**Ohun ẹbẹ si Ọlọrun.**

8. Oluwa Ọlọrun awọn ọmọ-ogun, gbọ adura mi; fi eti si i, Ọlọrun Jakọbu.
9. Kiyesi i, Ọlọrun asà wa, si ṣíjú wọ̀ ojú Ẹni-àmì òróró rẹ. (Gen 15:1; Psm 2:2.)
10. Nitori pe ọjọ kan ninu agbala rẹ sànju ẹgbẹrun ọjọ lọ. Mo fẹ ki nkuku maa ṣe adènà ni ile Ọlọrun mi, ju lati maa gbe agọ iwa-buburu. (1 Kro 23:5.)
11. Nitori Oluwa Ọlọrun ni òòrùn ati asa: Oluwa yoo fun ni ni oore-ofẹ, ati ogo, kò si ohun rere ti yoo fà sẹ́hìn lọ́wọ́ awọn ti nrin deede.
12. Oluwa awọn ọmọ-ogun, ibukun ni fun oluwarẹ naa ti o gbẹkẹle ọ. (Psm 2;12.)

ORIN 85.

**Aanu Oluwa lati ẹ̀hìn wa.**

OLUWA, iwọ ti nṣe ojú rere si ilẹ̀ rẹ: iwọ ti mu igbèkùn Jakọbu pada bọ̀. (Esra 1:11; Jer 30:18; Esk 39:25.)
2. Iwọ ti dárí aiṣedeede awọn eniyan rẹ ji, iwọ ti bò gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ wọn mọ́lẹ̀. (Psm 103:3; 32:1.)
3. Iwọ ti mu gbogbo ibinu rẹ kuro: iwọ ti yipada kuro ninu gbígbóná ibinu rẹ. (Psm 78:38; Deut 13:17.)

**Adura fun isoji.**

4. Yi wa pada, Ọlọrun igbala wa, si mu ibinu rẹ si wa kúro. (Psm 80:3–7.)
5. Iwọ o binu si wa titi lae bi? Iwọ o fa ibinu rẹ jade lati irandiran bi? (Psm 74:1; 79:5; 80:4.)
6. Iwọ ki yoo ha tun mu wa sọjí, ki awọn eniyan rẹ lè maa yọ̀ ninu rẹ? (Hab 3:2.)
7. Oluwa fi aanu rẹ hàn fun wá, ki o si fun wa ni igbala rẹ. (Psm 106:4.)

**Aanu ati otitọ Oluwa.**

8. Jẹ ki emi gbọ́ bi Ọlọrun Oluwa yoo ti wí: nitori ti yoo sọ alaafia si awọn eniyan rẹ, ati si awọn eniyan mímọ́ rẹ: ṣugbọn ki wọn má tun padà si iwà-wèrè wọn mọ́. (Hab 2:1; Sek 9:10.)
9. Nitootọ igbala rẹ sunmọ awọn ti o bẹru rẹ; ki ogo le maa gbé ilẹ̀ wa. (Isa 46:13; Sek 2:5; Jhn 1:14.)
10. Aanu ati otitọ yoo padera; ododo ati alaafia yoo fi ẹnu ko ara wọn lẹnu. (Psm 72:3; Isa 32:17; Luk 2:14.)
11. Otitọ yoo ru jade lati ilẹ̀ wá: ododo yoo si bojuwo ilẹ̀ lati ọ̀run wá.

12. Nitootọ Oluwa yoo fúnni ni èyí ti o dara; ilẹ̀ wa yoo si maa mu àsunkún rẹ̀ wá. (Psm 84:11; Jak 1:17.)
13. Ododo yoo ṣaaju rẹ̀; yoo si fi ipasẹ rẹ ṣe ọ̀nà. (Psm 89:14.)

## ORIN 86

**Ìpè fun iranwọ nigba ipọnju.**

OLUWA, dẹ etí rẹ silẹ, gbohun mi: nitori ti emi ṣe talaka ati alaini. (Psm 17:6; 40:17.)
2. Pa ọkàn mi mọ́; nitori emi ni ẹni ti iwọ ṣe ojurere fún: iwọ, Ọlọrun mi, gba ọmọ ọdọ rẹ ti o gbẹkẹle ọ. (Psm 25:20; 4:3; 31:14.)
3. Ṣàánú fun mi, Oluwa: nitori iwọ ni emi nke pe lojojumọ. (Psm 57:1; 88:9.)
4. Mu ọkán iranṣe rẹ yọ̀: Oluwa, nitori iwọ ni mo gbe ọkàn mi soke sí. (Psm 35:1; 143:8.)
5. Nitori iwọ, Oluwa, o ṣeun, o si mura ati dariji; o si pọ̀ ni aanu fun gbogbo awọn ti nke pè ọ. (Psm 130:7; 145:9; Joel 2:13.)
6. Oluwa, fi eti si adura mi; si fiyè si ohùn ẹbẹ mi. (Psm 55:1.)
7. Ni ọjọ ipọnju mi, emi o ke pe ọ: nitori ti iwọ ndá mi lóhùn. (Psm 50:15; 17:6.)

**Ìyìn fun Ọlọrun.**

8. Oluwa, ninu awọn oriṣa kò si ọkan ti o dabi rẹ, bẹẹ ni kọ si iṣẹ́ kan ti o dabi iṣẹ́ rẹ. (Esk 15:11; Psm 89:6; Deut 3:24.)
9. Gbogbo awọn orilẹ-èdè ti iwọ da ni yoo wá, wọn o si sin niwaju rẹ, Oluwa; wọn o si maa fi ogo fun orukọ rẹ. (Psm 22:31; Isa 43:7; Ifh 15:4.)
10. Nitori pé iwọ pọ̀, iwọ si nṣe ohun iyanu: iwọ nikan ni Ọlọrun. (Eks 15:11; Psm 72:18; Deut 6:4; Mk 12:29.)

**Ẹbẹ̀ ati ọpẹ́.**

11. Oluwa, kọ̀ mi ni ọ̀nà rẹ; emi o maa rin ninu otitọ rẹ: mu àyà mi ṣọkan lati bẹru orukọ rẹ. (Psm 25:4.)
12. Emi o yin ọ, Oluwa Ọlọrun mi, tinutinu mi gbogbo: emi o si maa fi ogo fun orukọ rẹ titi lae. (Psm 111:1.)
13. Nitori pé nla ni aanu rẹ si mi: iwọ si ti gbà ọkàn mi lọwọ isà-òkú jinjin. (Psm 30:3.)

**Idaniloju aanu Ọlọrun ati oore-ọfẹ.**

14. Ọlọrun, awọn agbẹraga dide si mi, ati ìjọ awọn alagbara nwá ọkàn mi kiri; wọn ko si fi ọ pè ni oju wọn. (Psm 54:3.)
15. Ṣugbọn iwọ, Oluwa, ni Ọlọrun ti o kun fun iyọ́nú, ati oloore-ọfẹ, olupamọra, o si pọ̀ ni aanu ati otitọ. (Eks 34:6; Neh 9:17; Psm 103:8; Joel 2:13.)
16. Yipada si mi si ṣaanu fun mi; fi ipa rẹ fun iránṣẹ́ rẹ, si gbà ọmọkunrin iranṣẹbinrin rẹ là. (Psm 25:16; 68:35; 116:16.)
17. Fi àmì hàn mi fun rere; ki awọn ti o korira mi le ri i, ki ojú le ti wọn, nitori iwọ, Oluwa, ni o ti ràn mi lọwọ ti o si tù mi ninu. (Psm 112:10; 118:13.)

## ORIN 87

**Sioni ri ojú rere Ọlọrun.**

IPILE rẹ̀ nbẹ lori awọn òkè mimọ.
2. "Oluwa fẹ ẹnu-ọ̀na Sioni jù gbogbo ibùjókòó Jakobu lọ. (Psm 78:67.)
3. Ohun ogo ni a nsọ ni tirẹ, Ìlú Ọlọrun. (Isa 60:1.)
4. Emi o da orukọ Rahabu ati Bakiloni laarin awọn ti o mọ̀ mi: kiyesi Filistini ati Tire, pẹlu Etiopia: "A bí eleyìí nibẹ" ni wọn wí.
5. Ati ni Sioni ni a o wi pé: "Ọkunrin yìí ati ọkunrin naa ni a bi ninu rẹ̀;" ati Ọgá-ògo tikararẹ ni yoo fi ẹsẹ̀ rẹ̀ mulẹ. (Psm 48:8.)
6. Oluwa yoo kà, nigba ti o ba nkọ orukọ awọn eniyan, pe, "A bi eleyìí nibẹ." (Esk 13:9.)
7. Ati awọn olorin ati awọn ti nlu ohun-èlò orin yoo wi pé: "Gbogbo orisun mi nbẹ ninu rẹ." (Psm 36:9.)

## ORIN 88.

**Ipe si Ọlọrun fun iranlọwọ.**

OLUWA Ọlọrun igbala mi, emi nkigbe lọsan ati loru niwaju rẹ. (Psm 27:9; 51:14.)

2. Jẹ ki adura mi wa si iwaju rẹ: dẹ etí rẹ silẹ̀ si igbe mi. (Psm 18:6.)

**Iponju olórin naa.**

3. Nitori ti ọkàn mi kún fun ipọnju, ẹmi mi si súnmọ́ isà-òkú. (Psm 107:18–26.)

4. A kà mi pẹlu kún awọn ti o sọkalẹ lọ si ihò; emi dabi ọkunrin ti ko ni ipá. (Psm 28:1.)

5. Ẹni ti a kọ̀ silẹ laarin awọn òkú, bi awọn ẹni pipa ti o dubulẹ ni isà-òkú, ẹni ti iwọ ko ranti mọ́: a si ge wọn kuro nipa ọwọ́ rẹ. (Isa 53:8.)

6. Iwọ ti fi mi le ibi isalẹ̀ ti o jin julọ, ninu òkùnkùn, ninu ọgbun. (Psm 86:13; 143:69:15.)

7. Ibinu rẹ lẹ̀ mọ mi lara kikan, iwọ si ti fi rírú omi rẹ gbogbo ba mi jà. (Psm 42:7.)

8. Iwọ ti mu awọn ojulumọ mi jinnà si mi; iwọ si sọ mi di irira si wọn; a sé mi mọ́, kò le jade. (Job 19:13; Psm 31:11; 142:4; E.Jer. 3:7.)

9. Ojú mi nkaanu nitori iponju: Oluwa, emi ti npè ọ lojojumọ, emi si ti nawọ́ mi si ọ. (Psm 38:10; 86:3; Job 11:13; Psm 143:6.)

**Ibeere olórin naa.**

10. Iwọ o fi iṣẹ́ iyanu rẹ hàn òkú bí? Awọn òkú yoo ha dide ki wọn si maa yìn ọ bí? (Psm 6:5; Isa 38:18.)

11. A o ha fi iṣeun ìfẹ́ rẹ hàn ni iboji bi? Tabi otitọ rẹ ninu iparun?

12. A ha le mọ̀ iṣẹ́ iyanu rẹ ni okunkun bí? Ati ododo rẹ ni ilẹ igbagbe? (Job 10:21.)

13. Ṣugbọn iwọ ni mo kigbe sí, Oluwa: ati kutukutu owuro ni adura mi yoo wa siwaju rẹ. (Psm 5:3; 119:147.)

14. Oluwa, eeṣe ti iwọ fi ṣa ọkàn mi tì? Eeṣe ti iwọ fi pa ojú rẹ mọ́ kuro lọdọ mi? (Job 13:24; Psm 13:1.)

**Ẹdùn-ọkàn olórin naa.**

15. Ìṣẹ́ nṣẹ mi, emi mura àti kú lati ìgbà èwe mi wá: nigba ti ẹ̀rù rẹ ba nba mi, emi di gbére-gbère. (Job 6:4.)

16. Ìfẹ́jú ibinu rẹ kọja lara mi; ibẹru rẹ ti ge mi kuro.

17. Wọn wa yi mi ka lọjọ gbogbo bi omi: wọn jùmọ̀ yi mi ká. (Psm 22:16.)

18. Olùfẹ ati ọrẹ ni iwọ mú jinnà si mi, ati awọn ojulumọ mi wà ninu okunkun. (Job 19:13; Psm 31:11; 38:11.)

## ORIN 89.

**Majẹmu pẹlu Dafidi.**

EMI o maa kọrin aanu Oluwa laelae: ẹnu mi lemi o maa fi fi otitọ rẹ hàn lati irandiran. (Psm 101:1.)

2. Nitori ti emi wi pe, A o gbé aanu rẹ soke laelae: otitọ rẹ ni iwọ o gbé kalẹ lọrun. (Psm 103:17; 36:5.)

3. "Emi ti bá àyànfẹ́ mi dá majẹmu emi ti búra fun Dafidi, iranṣẹ mi." (1 A.Ọba 8:16; Psm 132:11.)

4. "Irú ọmọ rẹ ni emi o gbé kalẹ̀ laelae, emi o si maa gbé ìtẹ́ rẹ ró lati irandiran. (2 Sam 7:16; Isa 9:7; Luk 1:33.)

**Ìyìn fun Ọlọrun otitọ ati alagbara.**

5. Ọrun yoo si maa yìn iṣẹ́-iyanu rẹ, Oluwa, otitọ rẹ pẹlu ninu ijọ eniyan mímọ́ rẹ. (Psm 19:1; 149:1.)

6. Nitori pé, "Tani o wà ni ọrun ti a le fi wé Oluwa? Tani ninu awọn ọmọ alagbara, ti a le fi wé Oluwa. (Mika 7:18; Psm 29:1.)

7. Ọlọrun ni o ni ibẹru gidigidi ni ijọ eniyan mímọ́, ó si ni ìbuyìn-fún lati ọdọ gbogbo awọn ti o yi i ká. (Psm 47:2; 96:4.)

8. Oluwa, Ọlọrun awọn ọmọ-ogun, tani Oluwa alagbara bi iwọ? Tabi bi otitọ rẹ ti o yi ọ ká. (Psm 71:19.)

9. Iwọ ni o nṣàkóso ibinu okun; nigba ti rírú omi rẹ̀ dide, iwọ mu un pa rọ́rọ́. (Psm 65:7.)

10. Iwọ ni o ti ya Rahabu pérepère bi ẹni ti a pa; iwọ ti fi apá ọwọ́ agbara rẹ tú awọn ọ̀tá rẹ ká. ( Psm 87:4; Isa 51:9; Psm 68:1.)

11. Ọrun ni tirẹ, ayé pẹlu ni tirẹ, ayé ati ẹkun rẹ, iwọ ni o ti ṣe ipilẹ wọn. (1 Kro 29:11; Psm 24:1,2.)

12. Ariwa ati gusu iwọ ni o ti da wọn; Taboru ati Hermoni yoo maa yọ̀ ni orukọ rẹ. (Jos 19:22; 12:1.)

13. Iwọ ni apá agbara: agbara ni ọwọ́ rẹ, giga ni ọwọ́ ọ̀tún rẹ. (Psm 98:1.)

14. Otitọ ati idajọ ni ibùjokòó itẹ́ rẹ: aanu ati otitọ ni yoo maa lọ siwaju rẹ. ( Psm 97:2; 85:13.)

15. Ibukun ni fun awọn eniyan ti o mọ ohùn ayọ̀: Oluwa, wọn o maa rin ni imọlẹ ojú rẹ. (Num 10:10.)

16. Ni orukọ rẹ ni wọn o maa yọ ni ọjọ gbogbo: ati ninu ododo rẹ ni a o maa gbe wọn lékè.

17. Nitori iwọ ni ogo agbara wọn; ati ninu ọre ojurere rẹ ni a o gbe iwo wa sókè. (Psm 28:8; 75:10.)

18. Nitori Oluwa ni asà wa: Ẹni-Mimọ Israẹli ni ọba wa. (Psm 47:9; 71:22.)

**Ìlérí Ọlọrun fún Dafidi.**

19. Nigba naa ni iwọ sọ ni ojú iran fun ayanfẹ rẹ, o si wi pe, "Emi ti gbé iranlọwọ ru ẹni-alagbara; emi ti gbé ẹnikan lékè ti a yàn ninu awọn eniyan. (1 A.Ọba 11:34.)

20. Emi ti ri Dafidi, iranṣẹ mi: òróró mi mímọ́ ni mo ta si i lori. (A.A. 13:22; 1 Sam 16:1–12.)

21. Nipasẹ ẹni ti a o fi ọwọ́ mi mulẹ: apa mi pẹlu yoo maa mu un lara le.

22. Ọtá ki yoo fagbára-gbà lọdọ rẹ; bẹẹ ni awọn ọmọ ìwà-buburu ki yoo pọn ọn lójú. (2 Sam 7:10.)

23. Emi o si lu awọn ọta rẹ bolẹ niwaju rẹ, emi o si yọ awọn ti o korira rẹ lẹnu. (2 Sam 7:9.)

24. Ṣugbọn otitọ mi ati aanu mi yoo wà pẹlu rẹ; ati ni orukọ mi ni a o gbe ìwo rẹ soke. (2 Sam 7:15.)

25. Emi o gbè ọwọ́ rẹ le òkun, ati ọwọ́ ọ̀tún rẹ le odò nla.

26. Oun o kigbe pè mi pe, "Iwọ ni baba mi, Ọlọrun mi, ati apata igbala mi." (2 Sam 7:14; 22:47.)

27. Emi o si ṣe e ni akọbi, Ẹni-giga ju awọn ọba ayé lọ. (Kol 1:15; Num 24:7; Ifh 1:5.)

28. Aanu mi ni emi o pamọ fun un laelae, ati majẹmu mi yoo si ba a duro ṣinṣin. (Isa 55:3.)

29. Irú-ọmọ rẹ pẹlu ni emi o mu pẹ́ titi, ati itẹ́ rẹ kí ọjọ ọrun. (Isa 9:7; Jer 33:17; Deut 11:21.)

30. Bi awọn ọmọ rẹ bá kọ ofin mi silẹ, ti wọn kò si rìn nipa idajọ mi. (2 Sam 7:14.)

31. Bi wọn bá ba ilana mi jẹ́, ti wọn ko si pa ofin mi mọ.

32. Nigba naa ni emi ó fi ọ̀gọ̀ bẹ irekọja wọn wò, ati ẹ̀ṣẹ̀ wọn pẹlu iná. (2 Sam 7:14.)

33. Ṣugbọn iṣeun-ifẹ mi ni emi ki yoo gbà lọwọ rẹ, bẹẹ ni emi ki yoo jẹ́ ki otitọ mi o yẹ̀. (2 Sam 7:15.)

34. Majẹmu mi ni emi ki yoo dà, bẹẹ ni emi ki yoo yi ohun ti o ti ètè mi jáde pada. (Deut 7:9; Num 23:19.)

35. Lẹẹkan ni mo ti fi ìwà-mimọ mi bura pé, "Emi ki yoo purọ fun Dafidi." (Amos 4:2.)

36. Irú-ọmọ rẹ yoo duro titi laelae, ati ìtẹ́ rẹ bi òòrùn niwaju mi. (Psm 72:5.)

37. "A o fi idi rẹ mulẹ laelae bi òṣùpá, ati bi ẹlẹri otitọ ni ọ̀run."

**Ìjiyà lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun wá.**

38. Ṣugbọn iwọ ti ṣá tì, iwọ si korira, iwọ ti binu si Ẹni-àmì òróró rẹ. (1 Kro 28:9; Deut 32:19.)

39. Iwọ ti sọ majẹmu iranṣẹ rẹ di òfo: iwọ ti sọ adé rẹ si ilẹ. (E.Jer. 5:16.)

40. Iwọ ti fa ọgbà rẹ gbogbo ya: iwọ ti mu ilu-olodi rẹ di ahoro. (Psm 80:12; E.Jer. 2:2–5.)

41. Gbogbo awọn ti nkọja lọ ni ọ̀nà nfi ṣe ìjẹ: oun si di ẹ̀gàn fun awọn aladugbo rẹ. (Psm 44:13.)

42. Iwọ ti gbe ọwọ́ ọ̀tún awọn ọta rẹ̀ soke; iwọ mu gbogbo awọn ọ̀tá rẹ̀ yọ̀. (Psm 13:2; 80:6.)

43. Iwọ si ti yí ojú idà rẹ̀ pada pẹlu, iwọ ko si mu un duro lójú ogun. (Psm 44:10.)

44. Iwọ ti mu ogo rẹ̀ kùnà, iwọ si wo ìtẹ́ rẹ palẹ̀ sílẹ̀ẹ́lẹ̀. (Esk 28:7.)

45. Ọjọ èwe rẹ̀ ni iwọ gé kúrú; iwọ fi ìtìjú bo o. (Psm 102:23; 44:15.)

**Adura lati ṣe atunṣe.**

46. Yoo ti pẹ to, Oluwa? Iwọ o pa ara rẹ mọ laelae? Ibinu rẹ yoo ha jò bi iná bi? (Psm 79:5.)

47. Ranti bi ọjọ mi ti kuru tó; eeṣe ti iwọ ha da gbogbo eniyan lásan? (Job 7:7; 10:9; 14:1; Psm 39:5.)

48. Ọkunrin wo ni o wà láàyè, ti ki yoo ri ikú? Ti yoo gba ọkàn rẹ lọ́wọ́ isà-òkú. (Psm 49:9; Heb 11:5.)

49. Oluwa, nibo ni iṣeun-ifẹ rẹ atijọ wà, ti iwọ bura fun Dafidi ninu otitọ rẹ? (2 Sam 7:15; Psm 54:5.)

50. Oluwa, ranti ẹ̀gàn awọn iranṣẹ rẹ, ti emi nrù ni àyà mi lati ọdọ gbogbo ọpọ eniyan. (Psm 69:9–19.)

51. Ti awọn ọ̀tá rẹ fi kẹ́gàn, Oluwa: ti wọn fi ngàn ipaṣẹ Ẹni-àmì òróró rẹ. (Psm 74:10.)

52. "Olubukun ni Oluwa si i titi laelae: Amin ati Amin." (Psm 41:13.)

## IWE KẸRIN

## ORIN 90.

**Ọlọrun ayérayé ati eniyan ti nku. Adura Mose, eniyan Ọlọrun.**

OLUWA, iwọ ni o ti nṣe ibùjókòó wa lati irandiran. (Deut 33:27; Esk 11:16.)

2. Ki a to bi awọn òkè nla ati ki ìwọ to da ilẹ̀ ati ayé, àní lati ayérayé iwọ ni Ọlọrun. (Owe 8:25; Psm 102:25; 93:2.)

3. Iwọ sọ eniyan di ìbàjẹ́ iwọ si wi pe, "Ẹ pada wá, ẹ̀yin ọmọ eniyan. (Gen 3:19.)

4. Nitori pé ìgbà ti ẹgbẹrun ọdún ba kọja loju rẹ̀, bi àná ni o ri, kí ìgbà ìṣọ́ kan loru. (2 Pet 3:8; Psm 39:5.)

5. Iwọ kó wọn lọ bi ẹni pé ni ṣíṣàn-omi; wọn dabi oorun; ni kutukutu wọn dabi kòriko ti o dàgbà sókè. (Job 27:20; Psm 73:20; 103:15; Isa 40:6.)

6. Ni kutukutu o ni àwọ̀ lara, o si dàgbà soke, ni aṣalẹ a gè e lulẹ, o si rọ. (Job 14:2; Psm 92:7.)

7. Nitori awa di ègbé nipa ibinu rẹ, ati nipa ibinu rẹ ara kò rọ̀ wá.

8. Iwọ ti gbé ẹ̀ṣẹ̀ wa ka iwaju rẹ, ohun ìkọ̀kọ̀ wa nbẹ ninu imọlẹ iwaju rẹ̀. (Psm 50:21; Jer 16:17; Psm 19:12.)

9. Nitori ọjọ wa gbogbo nyipo lọ ninu ibinu rẹ: awa nló ọjọ́ wa bi alá ti a nrọ́. (Psm 78:33.)

10. Adọrin ọdún ni iye ọjọ́ ọdún wa; bi o si ṣe pe nipa ti agbara, bi wọn bá to ọgọrin ọdún, agbara wọn làálàá pẹlu ibanujẹ ni; nitori pe a ko ni pẹ ge e kuro, awa a si fo lọ. (Onws 12:2–7.)

11. Tani o mọ agbara ibinu rẹ? Gẹgẹ bi ẹ̀rù rẹ, bẹẹ ni ibinu rẹ. (Psm 76:7.)

12. Bẹẹ ni iwọ kọ́ wa lati maa ka iye ọjọ́ wa, ki awa le fi ọkàn wa sipa ọgbọ́n. (Psm 39:4.)

**Adura fun aanu Ọlọrun.**

13. Pada, Oluwa, yoo ti pẹ tó? Yi ọkàn pada nitori awọn ọmọ-ọ̀dọ̀ rẹ. (Deut 32:26; Psm 35:14.)

14. Fi aanu rẹ tẹ́ wa lọ́rùn ni kutukutu ki awa le maa yọ̀, ati ki inu wa le maa dun ni ọjọ́ wa gbogbo. (Psm 65:4; 85:6.)

15. Mu inú wa dùn bi iye ọjọ ti iwọ pọ́n wa lójú, ati iye ọdun ti awa ti nri buburu.

16. Jẹ ki iṣẹ́ rẹ hàn si awọn ọmọ-ọdọ rẹ ati ogo rẹ si awọn ọmọ wọn. (Hab 3:2; 1 A.Ọba 8:11.)

17. Jẹ ki ẹwà Oluwa Ọlọrun wa wà lara wa: ki iwọ si fi ìdí iṣẹ́ ọwọ́ wa múlẹ̀ lara wa, bẹẹ ni iṣẹ́ ọwọ́ wa ni ki iwọ o fi ìdí rẹ múlẹ̀. (Psm 27:4; Isa 26:12.)

## ORIN 91.

**Ileri ààbò.**

ENI ti o jókòó ni ibi ìkọ̀kọ̀ Ọgá-ògo ni yoo maa gbe abẹ́ ojiji Olodumare. (Psm 27:5; 31:20; 17:8.)

2. Emi o wi fun Ọlọrun pé, "Iwọ ni ààbò ati odi mi; Ọlọrun mi, ẹni ti emi gbẹkẹle." (Psm 142:5.)

3. Nitootọ oun o gba ọ ninu ikẹkun awọn pẹyẹpẹyẹ ati ninu àjàkálẹ̀-àrùn búburú. (Psm 124:7.)

4. Yoo fi iyẹ́ rẹ̀ bo ọ, abẹ́ iyẹ́-apá rẹ̀ ni iwọ o si gbẹkẹle: otitọ rẹ̀ ni yoo ṣe asà ati apata rẹ. (Isa 51:16; Psm 57:1; 40:11; 35:2.)

5. Iwọ ki yoo bẹ̀rù nitori ẹ̀rù òru; tabi fún ọfà ti nfo lọsán. (Psm 23:4; O.Sol. 3:8; Psm 64:4.)

6. Tabi fún àjàkálẹ̀-àrùn ti nrin kiri ni òkùnkùn, tabi fún iparun ti nrun-ni ní ọsángangan. (ẹsẹ 10; Job 5:22.)

7. Ẹgbẹrun yoo ṣubu ni ẹgbẹ rẹ, ati ẹgbaarun ni apa ọ̀tún rẹ: ṣugbọn ki yoo sunmọ ọ̀dọ̀ rẹ.

8. Kiki ojú rẹ ni iwọ o maa fi rí, ti o si maa fi wo ère awọn eniyan buburu. (Psm 37:34; Mal 1:5.)

**Ẹ̀rí Olorin naa.**

9. Nitori iwọ ti fi Oluwa ṣe ààbò rẹ, iwọ ti fi Ọgá-ògo ṣe ibugbe rẹ.

10. Buburu kan ki yoo ṣubu lu ọ. Bẹẹ ni arunkarun ki yoo sunmọ ilé rẹ. (Owe 12:21.)

11. Nitori ti yoo fi àṣẹ fun awọn angẹli rẹ̀ nitori rẹ, lati pa ọ mọ ni ọ̀nà rẹ gbogbo. (Psm 34:7; Matt 4:6; Luk 4:10; Heb 1:14.)

12. Wọn o gbe ọ soke ni ọwọ́ wọn, ki iwọ má ba fi ẹsẹ̀ rẹ gbún okuta.

13. Iwọ o kọja lori kinniun ati paramọ́lẹ ẹgbọrọ kinniun ati ejò ni iwọ o *fi ẹsẹ̀ tẹ-mọlẹ. (Luk 10:19.)*

**Ẹ̀rí ti Ọlọrun.**

14. Nitori ti o fẹ ìfẹ́ rẹ̀ si mi, nitori naa ni emi o ṣe gba a: emi o gbe e lèke, nitori ti o mọ orukọ mi. (Psm 145:20; 59:1; 9:10.)

15. Oun o pe orukọ mi, emi o si da a lohun: emi o pẹlu rẹ̀ ninu iponju, emi o gba a emi o si bu ọlá fun un. (Psm 50:15; 1 Sam 2:30; Jhn 12:26.)

16. Ẹmi gígùn ni emi o fi tẹ ẹ lọrun, emi o si fi ìgbàlà mi han an. (Psm 21:4; 50:23.)

## ORIN 92.

**Àṣẹ lati dupẹ.**
**Orin fun ọjọ́ isinmi.**

OHUN rere ni lati maa fi ọpẹ́ fun Oluwa, ati lati maa kọrin si orukọ rẹ, Ọgá-ògo. (Psm 147:1.)

2. Lati maa fi iṣeun ifẹ rẹ hàn ni owurọ, ati otitọ rẹ ni aṣálẹ́. (Psm 89:1.)

3. Lara ohun-èlò orin olókùn mẹwa, ati lara ohun-elo orin mímọ́: lara dùùrù pẹ̀lú ìró ti o ni ironu. (1 Kro 23:5; Psm 33:2.)

4. Nitori iwọ, Oluwa, ni o ti mú mi yọ̀ nipa iṣẹ́ rẹ̀: emi o maa kọrin iyin nitori iṣẹ́ ọwọ́ rẹ.

**Ọ̀pin oníwà-ipá.**

5. Oluwa, iṣẹ rẹ ti tobi tó! Iro-inu rẹ jinlẹ gidigidi. (Psm 40:5; Isa 28:29; Rom 11:33.)

6. Ọ̀pè eniyan kò mọ̀; bẹẹ ni òye ko ye aṣiwere (òmùgọ̀) eniyan. (Psm 73:22.)

7. Nigba ti awọn eniyan buburu ba rú bi koriko, ati ìgbà ti gbogbo awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ̀ ba ngbẹru: ki wọn le run laelae. (Psm 90:5; 94:4; 37:38; 93:4.)

8. Ṣugbọn iwo, Oluwa ni ẹni ti o ga titi lae. (Psm 83:18.)

9. Sa wò o, awọn ọ̀tá rẹ, Oluwa sa wò o, awọn ọ̀tá rẹ yoo ṣègbé; gbogbo oniṣẹ ẹ̀ṣẹ̀ ni a o tuka. (Psm 68:1; 89:10.)

*10. Ṣugbọn ìwo mi ni iwọ o gbé ga bi* ìwo agbanrere; ororo tuntun ni a o ta si mi lori. (Psm 89:17; 23:5.)

11. Oju mi pẹlu yoo ri ifẹ mi lara awọn ọta mi, eti mi yoo si maa gbọ́ ìfẹ́ mi si awọn eniyan buburu ti o dide si mi. (Psm 54:7; 59:10.)

**Òpin eniyan olododo.**

12. Olododo yoo gbà bi igi ọ̀pẹ: yoo dagba bi igi kedari Lebanoni. (Psm 52:8; Isa 65:22; Hos 14:5,6; Psm 104:16.)

13. Awọn ẹni ti a gbin ni ile Oluwa, yoo gbà ni agbala Ọlọrun wa. (Psm 80:15; 100:4.)

14. Wọn o maa so eso sibẹ ninu ogbó wọn: wọn o sanra, wọn o maa tutù nini. (Isa 37:31.)

15. Lati fi hàn pé, Ẹni diduro-ṣinṣin ni Oluwa: oun ni apata mi, kò si si aiṣododo kan ninu rẹ̀. (Deut 32:4; Psm 25:8; Rom 9:14.)

## ORIN 93.

**Ọlanla Ọlorun.**

OLUWA jọba, ọla-nla ni o wọ laṣọ; agbara ni Oluwa wọ laṣọ, o fi di ara rẹ ni amure: o si fi ìdí ayé múlẹ̀, ti ki yoo fi le yìí. (Psm 96:10; 97:1; 99:1; 104:1; 65:6.)

2. Lati ìgbà atijọ ni a ti fi ìdí ìtẹ́ rẹ kalẹ, ati ayé-rayé ni iwọ. (Psm 7:6; Gen 18:25; Psm 31:23.)

3. Ìṣàn-omi gbé ohùn wọn sókè, Oluwa, ìṣàn-omi gbé ohun wọn soke; iṣan-omi gbé rírú omi wọn soke. (Psm 98:7,8.)

4. Oluwa ni ologo, o ni ògo ju ariwo omi pupọ lọ, ju riru omi nla, ani ju agbara rírú omi òkun lọ. (Psm 65:7; 89:9.)

5. Otitọ ni ẹ̀rí rẹ; iwa-mimọ ni o yẹ ile rẹ laelae Oluwa. (Psm 19:7; 1 Kor 3:17.)

## ORIN 94.

**Ìpè fun ẹ̀san lori eniyan buburu.**

OLUWA, Ọlọrun ẹ̀san; Ọlọrun ẹ̀san, fi ara rẹ hàn. (Deut 32:35; Nah 1:2; Psm 50:2.)

2. Gbé ara rẹ sókè, iwọ onidajọ ayé: san ẹ̀san fun awọn agberaga. (Psm 7:6; Gen 18:25; Psm 31:23.)

3. Oluwa, yoo ti pẹ tó ti awọn eniyan buburu, yoo ti pẹ to ti awọn eniyan buburu yoo fi maa borí? (Job 20:5.)

4. Wọn o ti maa dà ọ̀rọ̀ nù ti wọn o maa sọ ohun líle pẹ́ tó? Ti gbogbo oniṣẹ ẹ̀ṣẹ̀ yoo fi maa fi ara wọn leri. (Psm 31:18; 10:3.)

5. Oluwa, wọn fọ́ awọn eniyan rẹ túútúú wọn si nyọ awọn eniyan rẹ lẹnu.

6. Wọn pa awọn opó ati alejo, wọn si pa ọmọ alaini-baba. (Isa 10:2.)

7. Sibẹ wọn wi pé, "Oluwa ki yoo ri i, bẹẹ ni Ọlọrun Jakọbu ki yoo ka a sí. (Psm 10:11.)

8. Ki òye ye yin, ẹyin òpè ninu awọn eniyan: ati ẹyin aṣiwere (òmùgọ̀) nigbawo ni ẹyin o gbọ́n? (Psm 92:6.)

9. Ẹni ti o gbin etí, o le ṣe alaigbọ́ bi? Ẹni ti o da ojú, o ha le ṣe alairiran? (Eks 4:11; Owe 20:12.)

10. Ẹni ti nbá awọn orilẹ̀-èdè wí, kò ha lè tọ́ni sọ́nà bi? Ẹni ti nkọ́ni hà lè ṣài ní ìmọ̀ bi? (Psm 44:2; Job 35:11; Isa 28:26.)

11. Oluwa mọ èrò-inú eniyan pé, asán ni wọ́n. (1 Kro 3:20.)

**Oluwa ki yoo kọ awọn eniyan rẹ silẹ.**

12. Ìbùkún ni fun eniyan naa ẹni ti iwọ naa, Oluwa, ti iwọ si kọ́ lati inu ofin rẹ wa. (Job 5:17; Heb 12:5.)

13. Ki iwọ le fun un ni isinmi, kuro ni ọjọ́ ibi, titi a o fi wà ihò silẹ fun eniyan buburu. (Psm 49:5; 9:15.)

14. Nitori pé Oluwa ki yoo ṣá awọn eniyan rẹ̀ ti, bẹẹ ni ki yoo kọ awọn eniyan-ini rẹ silẹ̀. (1 Sam 12:22; Rom 11:1,2.)

15. Ṣugbọn idajọ yoo pada si ododo: gbogbo ọlọ́kàn diduro ni yoo si maa tọ ọ lẹhin.

**Olorin naa nwa Oluwa.**

16. Tani yoo dide si awọn oluṣe buburu fun mi? Tabi tabi yoo dide si awọn oniṣẹ ẹ̀ṣẹ̀ fun mi?

17. Bikọṣe bi Oluwa ti ṣe olùrànlọ́wọ́ mi; ọkàn mi fẹ́rẹ̀ jókòó ni idakẹ. (Psm 124:1.)

18. Nigba ti mo rò pe, "Ẹsẹ̀ mi yọ̀". Oluwa, aanu rẹ di mi mu. (Psm 38:16.)

19. Ninu ọ̀pọ̀lọpọ̀ ibanujẹ inu mi, ìtùnú rẹ ni o nmu inú mi dùn. (Isa 66:13.)

20. Ìtẹ́ ẹ̀ṣẹ̀ ha le ba ọ kẹ́gbẹ́ pọ̀, ti nfi òfin dimọ́ ìwà-ìkà? (Amos 6:3; Isa 10:1.)

21. Wọn kó ara wọn jọ pọ̀ si ọkàn olododo, wọn si da ẹ̀jẹ̀ alaiṣẹ lẹbi. (Psm 56:6; Matt 27:1; Owe 17:15.)

22. Ṣugbọn Oluwa ni ààbò mi; Ọlọrun mi si ni apata ààbò mi. (Psm 59:9; 71:7.)

23. Oun o si mu ẹ̀ṣẹ̀ wọn bọ sori ara wọn, yoo si ge wọn kuro ninu ìwà-buburu wọn: Oluwa Ọlọrun wa, yoo gé wọn kuro. (Psm 7:16.)

ORIN 95.

**Kíkọ orin ìyìn.**

EWÁ, ẹ jẹ ki a kọrin si Oluwa: ẹ jẹ ki a hó ìhó ayọ̀ sí apata ìgbàlà wa. (Psm 100:1; Deut 32:15; 2 Sam 22:47.)

2. Ẹ jẹ ki a fi ọpẹ́ wa si iwaju rẹ̀, ki a si fi orin mímọ́ hó ìhó ayọ̀ si ọdọ rẹ̀. (Mika 6:6; Psm 100:4; 81:2.)

3. Nitori Oluwa, Ọlọrun ti o tobi ni, ati Ọba ti o tobi ju gbogbo òrìṣà lọ. (O.D. 96:4; 97:9; 135:5.)

4. Ni ikawọ ẹni ti ibi ọ̀gbun ilẹ̀ wa: giga awọn òkè nla ni tirẹ̀ pẹlu.

5. Tirẹ̀ ni òkun, oun ni o si dá a: ọwọ́ rẹ̀ ni o si da iyàngbẹ ilẹ̀. (Gen 1:9,10.)

6. Ẹ wá, ẹ jẹ ki a wólẹ̀, ki a tẹriba: ẹ jẹ ki a kunlẹ niwaju Oluwa, Ẹlẹda wa! (Psm 99:5–9; 2 Kro 6:13; Psm 100:1.)

7. Nitori Oun ni Ọlọrun wa: àwa si ni eniyan papa rẹ̀, ati agutan ọwọ́ rẹ̀. Loni bi ẹ̀yin o ba gbọ́ ohùn rẹ̀. (Psm 79:13; 100:3; Heb 3:7–11.)

**Titẹle ibawi naa.**

8. Ẹ má ṣe sé àyà yin le, bi ti Meriba ati bi ọjọ́ naa ni Massa, ni aginju. (Eks 17:2,7; Deut 6:16.)

9. Nigba ti awọn baba yin dán mi wò, ti wọn wadi mi, ti wọn si ri iṣẹ́ mi. (Psm 78:18; 1 Kro 10:9.)

10. Fún ogoji ọdún ni inu mi fi bajẹ si iran naa, mo ni, "Eniyan ti o ṣìnà ni àyà ni wọn, wọn kò si mọ ọ̀nà mi." (Heb 3:10,17.)

11. Awọn ẹni ti mo si bura fun ni ibinu mi, pe, wọn ki yoo wọ ibi isinmi mi. (Heb 4:3,5.)

ORIN 96.

**Ipe lati yin Oluwa.**

Ẹ kọrin tuntun si Oluwa: ẹ kọrin si Oluwa gbogbo ayé. (1 Kro 16:23–33.)

2. Ẹ kọrin si Oluwa, fi ìbukun fun orukọ rẹ̀; ẹ maa fi igbala rẹ̀ han lati ọjọ de ọjọ. (Psm 71:15.)

3. Sọrọ ogo rẹ laarin awọn Keferi, ati iṣẹ́ ìyanu rẹ̀ laarin gbogbo eniyan. (Psm 145:12.)

4. Nitori ti Oluwa tobi, o si ni ìyìn pupọpupọ: Oun lo ní ibẹru ju gbogbo oriṣa lọ. (Psm 145:3; 18:3; 95:3.)

5. Nitori pe gbogbo oriṣa orilẹ-ede asán ni wọn: ṣugbọn Oluwa ni o da ọrun. (1 Kro 16:26; Psm 115:15.)

6. Ọla ati ọla-nla ni o wa niwaju rẹ̀: ipá ati ẹwà nbẹ ninu ibi mimọ rẹ̀. (Psm 104:1.)

**Gbogbo ayé ẹ yin Oluwa.**

7. Ẹ fi fun Oluwa, ẹ̀yin ibatan eniyan, ẹ fi ògo ati ipá fun Oluwa. (Psm 29:1,2.)

8. Ẹ fi ogo fun orukọ Oluwa: mu ọrẹ wá, ki ẹ si wa si agbala rẹ̀. (Psm 79:9.)

9. Ẹ maa sin Oluwa ninu ẹwa iwa-mimọ; ẹ wariri niwaju rẹ̀, gbogbo ayé. (Psm 29:2.)

**Oluwa oludajọ ododo.**

10. Ẹ wi laarin awọn Keferi pe, Oluwa jọba: nitootọ a o fi idi ayé mulẹ ti ki yoo le yẹ: Oun o fi ododo ṣe idajọ eniyan. (Psm 93:1; 67:4.)

11. Jẹ ki ọrun yọ̀, jẹ ki inu ayé dùn; jẹ ki òkun maa ho pẹlu ìkún rẹ. (Psm 97:1; 98:7.)

12. Jẹ ki oko kún fun ayọ̀, ati ohun gbogbo ti nbẹ ninu rẹ̀: nigba naa ni gbogbo igi igbo yoo maa yọ̀.

13. Niwaju Oluwa: nitori ti o nbọ wa, nitori ti nbọ wa ṣe idajọ ayé: yoo fi ododo ṣe idajọ ayé, ati ti eniyan ni yoo fi otitọ rẹ̀ ṣe. (Psm 67:4; Ifh 19:11.)

## ORIN 97.

**Ọlọrun njọba.**

OLUWA jọba; ki ayé yọ̀; jẹ ki inu ọpọlọpọ erekuṣu dùn. (Psm 96:10,11.)

2. Awọsanma ati okunkun yi i ka: ododo ati idajọ ni ibùjokòó itẹ́ rẹ̀. (1 A.Ọba 8:12; Psm 18:11; 89:14.)

3. Ina ṣaaju rẹ̀, o si jó awọn ọtá rẹ̀ yika kiri. (Psm 18:8; Dan 7:10; Hab 3:5; Heb 12:29.)

4. Manamana rẹ̀ kọ imọlẹ si ayé: ayé ri i, o si wariri. (Psm 77:18.)

5. Awọn ọkè nyọ́ bi ida niwaju Oluwa, niwaju Oluwa gbogbo ayé. (Mika 1:4; Jos 3:11.)

**Igbega Ọlọrun.**

6. Ọrun fi ododo rẹ̀ hàn, gbogbo orilẹ-èdè si ri ogo rẹ̀. (Psm 50:6.)

7. Ojú yoo ti gbogbo awọn ti o nsin ère fínfín, eni ti nfi ère ṣe ileri ara wọn: ẹ maa sin in, gbogbo ẹ̀yin ọlọrun. (Eks 20:4; Lef 26:1; Heb 1:6.)

8. Sioni gbọ́, inu rẹ̀ si dùn; awọn ọmọbinrin Juda yọ̀, Oluwa, nitori idajọ rẹ. (Psm 48:11.)

9. Nitori pe Iwọ Oluwa, ni o ga ju gbogbo ayé lọ: Iwọ ni a gbé ga ju gbogbo oriṣa lọ. (Psm 83:18; Eks 18:11; Psm 95:3.)

**Idande Ọlọrun fun olootọ.**

10. Ẹ̀yin ti o fẹ́ Oluwa, ẹ korira ibi: o pa ọkàn awọn eniyan mímọ́ rẹ̀ mọ́: o gbà wọn ni ọwọ́ awọn eniyan buburu. (Psm 34:14; Amos 5:15; Owe 2:8; Psm 37:39; Dan 3:28.)

11. A funrugbin imọ́lẹ̀ fun olododo, ati inú dídùn fun aláyà diduro. (Job 22:28; Psm 112:4.)

12. Ẹ yọ̀ ni ti Oluwa, ẹ̀yin olododo; ki ẹ si maa dupẹ ni iranti iwà-mímọ́ rẹ. (Psm 32:11; 30:4.)

## ORIN 98.

**Orin Ìgbàlà.**

Ẹ kọrin tuntun si Oluwa; nitori ti o ti ṣe ohun iyanu: ọwọ́ ọ̀tún rẹ̀, ati apá rẹ̀ mímọ́ lo fi mu igbàlà wa fun ara rẹ̀. (Psm 33:3; 40:5; Eks 15:6; Isa 52:10.)

2. Oluwa ti sọ igbàlà rẹ̀ di mímọ̀; ododo rẹ̀ ni o ti fi hàn nigbangba loju awọn Keferi. (Rom 3:25.)

3. O ti ranti aanu rẹ̀ ati otitọ rẹ̀ si awọn ara ilé Israẹli: gbogbo opin ayé ti ri igbàlà Ọlọrun wa. (Luk 1:54; Isa 49:6.)

**Pipe awọn eniyan lati yin Ọlọrun.**

4. Ẹ ho ìhó ayọ̀ si Oluwa, gbogbo ayé: ẹ ho yè! ẹ yọ̀ ki ẹ si maa kọrin ìyìn. (Psm 100:1.)

5. Ẹ maa fi dùùrù kọrin si Oluwa, pẹlu dùùrù ati ohùn orin-mímọ́.

6. Pẹlu ìpè ati ohùn fèrè, ẹho ihò ayọ̀ niwaju Ọluwa, Ọba. (Num 10:10.)

**Ìpè si ẹ̀dá gbogbo lati yin Ọlọrun.**

7. Jẹ ki òkun maa ho pẹlu ìkún rẹ̀; ayé, ati awọn ti nbẹ ninu rẹ̀. (Psm 96:11; 24:1.)

8. Jẹ ki odò maa pàtẹ́wọ́, ki awọn òkè maa ṣe àjọyọ̀. (Psm 93:3; 65:12.)

9. Niwaju Oluwa; nitori ti o nbọ̀ wá ṣe idajọ ayé: pẹlu ododo ni yoo fi ṣe idajọ ayé, ati awọn orilẹ-ede laiṣègbè. (Psm 96:10,13.)

## ORIN 99.

**Ìpè lati yin Oluwa.**

OLUWA jọba; jẹ ki awọn eniyan wárìrì: o jókòó lori awọn kerubu; ki ayé ta gbọn-ọngbọn-ọn. (Eks 25:22.)

2. Oluwa tobi ni Sioni: o si ga ju gbogbo orilẹ-èdè lọ. (Psm 97:9.)

3. Ki wọn yin orukọ rẹ ti o tobi, ti o si ni ẹ̀rù; mimọ ni Oun.

4. Agbara ọba fẹ idajọ pẹlu, iwọ fi idi aiṣegbe mulẹ; iwọ nṣe idajọ ati ododo ni Jakọbu. (Psm 11:7; 17:2; 103:6.)

5. Ẹ gbé Oluwa Ọlọrun wa ga, ki ẹ si foribalẹ nibi apoti ìtisẹ̀ rẹ̀: mimọ ni Oun. (Psm 132:7; 19:2.)

**Ìdí ti a ni lati fi yin Oluwa.**

6. Mose ati Aarọni wà ninu awọn alufa rẹ̀, ati Samueli pẹlu si wà ninu awọn ti npe orukọ rẹ̀: wọn kẹ pe Oluwa, o si dá wọn lóhùn. (Jer 15,1; Eks 14,15; 1 Sam 7,9.)

7. O ba wọn sọ̀rọ̀ ninu ọ̀wọ́n awọsanma: wọn pa ẹ̀rí rẹ̀ mọ́ ati ìlànà ti o fi fun wọn. (Eks 33:9.)

8. Iwọ da wọn lóhùn, Oluwa Ọlọrun wa: iwọ Ọlọrun ti o dariji wọn, ti o si san ẹ̀san iwa buburu wọn. (Psm 106:44; Num 14:20; Deut 9:20.)

9. Ẹ gbé Oluwa Ọlọrun wa ga, ki ẹ si maa sìn nibi oke mímọ́ rẹ̀; nitori Oluwa Ọlọrun wa mímọ́ ni. (Psm 34:3.)

## ORIN 100.

**Gbogbo eniyan ẹ yin Oluwa.**

ẸHÓ ìhó ayọ̀ si Oluwa, ẹ̀yin ilẹ gbogbo. (Psm 98:4.)

2. Ẹ fi ayọ̀ sin Oluwa: ẹ wa ti ẹ̀yin ti orin si iwaju rẹ̀.

3. Ki ẹ̀yin mọ pe Oluwa, Oun ni Ọlọrun: Oun ni o da wa, tirẹ̀ ni awa: awa ni eniyan rẹ̀, ati agutan pápá rẹ̀. (Psm 46:10; 95:6,7.)

4. Ẹ wọ ẹnu ọ̀nà rẹ̀ pẹlu ọpẹ́, ati si agbala rẹ̀ pẹlu ìyìn; ẹ maa dupẹ fun un, ki ẹ si maa fi ibukun fun orukọ rẹ̀. (Psm 11:7; 17:2; 103:6.)

5. Nitori ti Oluwa pọ̀ loore: aanu rẹ̀ kò nipẹkun; ati otitọ rẹ̀ lati irandiran. (Psm 132:7; 19:2.)

## ORIN 101.

**Ifẹ Dafidi ni lati ṣe olotitọ.**

EMI o kọrin aanu ati ti idajọ; Oluwa, si ọ ni emi o maa kọrin. (Psm 89:1.)

2. Emi o maa rin ìrìn mi pẹlu ọgbọ́n lọ́nà pípé. Nigbawo ni iwọ o tọ mi wa! Emi o maa rin ninu ilé mi pẹlu àyà pípé. (1 Sam 18:14; 1 A.Ọba 9:4.)

3. Emi ki yoo gbe ohun buburu siwaju mi; emi korira iṣẹ́ awọn ti o yapa, ki yoo fi ara mọ mi. (Deut 15:9; Psm 40:4.)

4. Agidi ọkàn yoo kuro lọ́dọ̀ mi: emi ki yoo mọ eniyan buburu. (Owe 11:20.)

**Ifẹ Dafidi ni pe ki gbogbo eniyan jẹ olotitọ.**

5. Ẹnikẹni ti o ba nsọrọ ẹnikeji rẹ lẹhin, oun ni emi o ge kuro: ẹni oloju giga ati igberaga àyà, oun ní emi ki yoo farada fún. (Psm 50:20; Owe 6:17.)

6. Ojú mi yoo wa lara awọn olootọ, ki wọn le maa ba mi gbé: ẹni ti o ba nrin ni ọ̀nà pípé, oun ni yoo maa sin mi. (Psm 119:1.)

7. Ẹni ti o ba nṣe ẹ̀tàn, ki yoo gbe inu ilé mi: ẹni ti o ba nṣèkèé ki yoo duro niwaju mi.

8. Lojojumọ ni emi o maa run gbogbo eniyan buburu ile naa; ki emi le ge gbogbo oluṣe buburu kuro ni ilu Oluwa. (Psm 75:10; 118:10–12.)

## ORIN 102.

**Adura oluponju, nigba ti o ni ibanujẹ, ti o si tú àròyé rẹ̀ jade niwaju Oluwa.**

GBỌ adura mi, Oluwa, si jẹ́ ki igbe mi wá ṣọ́dọ rẹ. (Eks 2:23; 1 Sam 9:16.)

2. Ma ṣe pa ojú rẹ mọ kuro lara mi ni ọjọ́ ti emi wà ninu ipọnju; dẹ eti rẹ si mi; ni ọjọ ti mo ba pè, da mi lohun lọ́gán. (Psm 69:17; 71:2.)

3. Nitori ti ọjọ mi run bi eefin, egungun mi si jona bi ààrò. (Jak 4:14; Job 30:30; Psm 31:10.)

4. Àyà mi lù, o si rọ bi koriko; tobẹẹ ti mo gbagbe lati jẹ ounjẹ mi. (Psm 37:2.)

5. Nitori ohun ikerora mi, egungun mi lẹ̀ mọ ẹran-ara mi. (E.Jer. 4:8.)

6. Emi dabi ẹyẹ-igún ni ijù: emi dabi òwiwí ibi ahoro. (Isa 34:11.)

7. Emi nṣọra, emi dabi ològoṣé niounnìkan ṣoṣo lori ilé. (Psm 77:4: 38:11.)

8. Awọn ọta mi ngàn mi ni ọjọ́ gbogbo; ati awọn ti nṣe ikanra si mi, wọn fi mi bu. (A.A. 26:11; 23:12.)

9. Emi sá jẹ eeru bi ounjẹ, emi si dà ohun mímu mi pọ̀ pẹlu omijé. (Psm 42:3.)

10. Nitori ikannu ati ibinu rẹ; nitori iwọ ti gbé mi soke, iwọ si gbe mi ṣánlẹ̀. (Psm 30:3; Job 30:22.)

11. Ọjọ́ mi dabi òjìji ti o nfa sẹhin; emi si nrọ bi koriko. (Job 14:2; ẹsẹ 4.)

**Ọlọrun ayeraye ni ibi isadi Sioni.**

12. Ṣugbọn iwọ, ni yoo duro laelae; ati iranti rẹ lati ìran de ìran. (Psm 9:7; E.Jer. 5:19; Psm 135:13.)

13. Iwọ o dide, iwọ o ṣaanu fun Sioni: nitori igba ati ṣe oju-rere si i, nitootọ, àkókò naa de. (Isa 60:10; Sek 1:12; Psm 75:2.)

14. Nitori ti awọn iranṣẹ rẹ̀ ṣe inu didun si okuta rẹ̀, wọn si kaanu erupẹ rẹ̀.

15. Bẹẹ ni awọn orilẹ-èdè yoo maa bẹ̀rù orukọ Oluwa, ati gbogbo ọba ayé. Yoo maa bẹ̀rù ogo rẹ. (1 A.Ọba 8:43; Psm 138:4.)

16. Nigba ti Oluwa yoo gbé Sioni ró, yoo farahan ninu ogo rẹ̀.

17. Yoo juba adura awọn alaini, ki yoo si gàn adura wọn. (Neh 1:6.)

18. Eyi ni a o kọ fun ìran ti nbọ; ati awọn eniyan ti a o dá yoo maa yin Oluwa. (Rom 15:4; Psm 22:31.)

19. Nitori ti o wò ilẹ lati òkè ibimímọ́ rẹ̀ wá; lati ọrun wá ni Oluwa bojuwo ayé. (Deut 26:15; Psm 33:13.)

20. Lati gbọ irora awọn ẹlẹwọ̀n; lati tú awọn ti a yàn si ikú silẹ. (Psm 79:11.)

21. Lati sọ orukọ Oluwa ni Sioni, ati ìyìn rẹ̀ ni Jerusalẹmu. (Psm 22:22.)

22. Nigba ti a kó awọn eniyan jọ pọ̀ ati awọn ijọba lati maa sin Oluwa. (Psm 86:9.)

**Idanilojú idande.**

23. O rẹ agbara mi silẹ̀ ni ọ̀nà; ọ mu ọjọ́ mi kúrú. (Job 21:21.)

24. Emi si wi pe, Ọlọrun mi, má ṣe mu mi kuro ni aarinmeji ọjọ́ mi: lati ìran-diran ni ọdun rẹ. (Isa 38:10; Psm 90:2; Hab 1:12.)

25. Lati igba atijọ ni iwọ ti fi ìpìlẹ̀ ayé sọlẹ̀: ọrun si ni iṣẹ́ ọwọ́ rẹ. (Gen 1:1; Heb 1:10; Psm 96:5.)

26. Wọn o ṣègbé, ṣugbọn Iwọ o duro; nitootọ gbogbo wọn ni yoo di ogbó bi aṣọ; bi ẹ̀wù ni iwọ o pàrọ̀ wọn, wọn o si pàrọ̀. (Isa 34:4; Matt 24:35; 2 Pet 3:7,10; Ifh 20:11;Heb 1:11.)

27. Ṣugbọn bakan naa ni Iwọ, ọdún rẹ kò ni òpin. (Mal 3:6; Heb 13:8; Jak 1:17; Heb 1:12.)

28. Awọn ọmọ awọn iranṣẹ rẹ yoo duro pẹ́, a o si fi ẹsẹ̀ irú-ọmọ wọn múlẹ̀, niwaju rẹ. (Psm 69:36; 89:4.)

## ORIN 103.

**Ìpè lati fi ibukun fun Oluwa.**

FI ibukun fun Oluwa, ìwọ ọkan mi, ati gbogbo ohun ti o wà ninu mi, fi ibukun fun orukọ rẹ mímọ́. (Psm 104:1; 33:21.)

2. Fi ibukun fun Oluwa, iwọ ọkan mi, má si gbàgbé gbogbo oore rẹ̀.

3. Ẹni ti o dárí gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ rẹ jì; ẹni ti o si wò gbogbo àrùn rẹ sàn. (Psm 130:8; Isa 43:25; Eks 15:26.)

4. Ẹni ti o ra ẹ̀mí rẹ kuro ninu iparun; ẹni ti o fi iṣeun-ìfẹ́ ati ìyọ́nú dé ọ ni adé. (Psm 49:15; 5:12.)

5. Ẹni ti o fi ohun didara tẹ ọ lọ́rùn: bẹẹ ni ìgbà èwe rẹ di ọ̀tun bi ti ìdì. (Isa 40:31.)

**Ibukun ni fun Ọlọrun alaanu.**

6. Oluwa ṣe ododo ati idajọ fun gbogbo awọn ti a nilara.

7. O fi ọ̀nà rẹ̀ hàn Mose, iṣẹ́ rẹ̀ fun awọn ọmọ Israẹli.

8. Oluwa ni alaanu ati oloore, o lọra lati binu, o si pọ̀ ni aanu. (Eks 34:6; Neh 9:17; Psm 145:8.)

9. Oun kii baniwi nigbagbogbo: bẹẹ ni ki i pa ibinu rẹ mọ laelae. (Psm 30:5; Isa 57:16; Jer 3:5.)

10. Oun kii ṣe si wa gẹgẹ bi ẹṣẹ wa; bẹẹ ni kii san an fun wa gẹgẹ bi aiṣedeede wa. (Esra 9:13.)

11. Nitori pé, bi ọrun ti ga si ilẹ, bẹẹ ni aanu rẹ tobi si awọn ti o bẹru rẹ. (Psm 36:5.)

12. Bi ila-oòrùn ti jinna si iwọ-ọòrùn, bẹẹ ni o mu irekọja wa jinnà kuro lọdọ wa. (2 Sam 12:13; Isa 38:17; Heb 9:26.)

13. Bi baba ti ṣe iyọnú si awọn ọmọ, bẹẹ ni Oluwa nṣe iyọnú si awọn ti o bẹrù rẹ. (Mal 3:17.)

**Ifẹ Ọlọrun ayérayé.**

14. Nitori ti o mọ ẹdá wa; o ranti pe erupẹ ni wa. (Isa 29:16; Gen 3:19.)

15. Bi o ṣe ti eniyan ni, ọjọ rẹ, dabi koriko: bi itànná eweko igbẹ, bẹẹ ni o gbilẹ. (1 Pet 1:24; Job 14:1,2.)

16. Nitori ti afẹfẹ fẹ kọja lọ lori rẹ, kò sì si mọ; ibùjokòó rẹ kò ni mọ ọn mọ. (Job 7:10.)

17. Ṣugbọn aanu Oluwa lati ayérayé ni lara awọn ti o bẹrù rẹ, ati ododo rẹ lati ọmọ de ọmọ.

18. Si awọn ti o pa majẹmu rẹ mọ, ati si awọn ti o ranti ofin rẹ lati ṣe wọn. (Deut 7:9.)

**Ìpè lati yin orukọ Ọlọrun.**

19. Oluwa ti pèsè itẹ rẹ ninu ọrun; ijọba rẹ ni o si bori ohun gbogbo. (Psm 11:4; 47:2.)

20. Ẹ fi ibukun fun Oluwa, ẹyin angẹli rẹ, ti o pọ ni ipá ti nṣe ofin rẹ, ti nfi etí si ohùn ọrọ rẹ. (Psm 148:2; Matt 6:10; Heb 1:14.)

21. Ẹ fi ibukun fun Oluwa, ẹyin ọmọ-ogun rẹ gbogbo; ẹyin iranṣẹ rẹ, ti nṣe ifẹ rẹ. (Psm 148:2.)

22. Ẹ fi ibùkún fun Oluwa, gbogbo iṣẹ rẹ ni ibi gbogbo ijọba rẹ: fi ibukun fun Oluwa, iwọ ọkàn mi!

ORIN 104.

**Ibẹrẹ iṣẹdá.**

FI ibùkún fun Oluwa, iwọ ọkàn mi. Oluwa Ọlọrun mi, Iwọ tobi jọjọ: ọla ati ọla-nla ni Iwọ wọ ni aṣọ. (Psm 103:1.)

2. Ẹni ti o fi imọlẹ bora bi aṣọ: ẹni ti o ta ọrun bi aṣọ títa. (Dan 7:9; Isa 40:22.)

3. Ẹni ti o fi omi ṣe itì igi-àjà iyẹwu rẹ: ẹni ti o ṣe awọsanma ni kẹkẹ rẹ, ẹni ti o nrin lori apá iyẹ afẹfẹ. (Amos 9:6; Isa 19:1; Psm 18:1,10.)

4. Ẹni ti o ṣe efuufu ni iranṣẹ; ati ọwọ-iná ni oniṣẹ rẹ. (Heb 1:7.)

**Ipilẹ ayé.**

5. Ẹni ti o fi ayé sọlẹ lori ipilẹ rẹ, ti ko le sipò padà laelae. (Job 26:7; Psm 24:2.)

6. Iwọ fi ibú omi bo o mọlẹ bi aṣọ: awọn omi duro lori òkè nla. (Gen 7:19.)

7. Nipa ibáwí rẹ wọn sá: nipa ohùn àárá rẹ, wọn yara lọ.

8. Awọn òkè nla nru sókè; awọn afonifoji nsọkalẹ si ibi ti Iwọ ti fi lélẹ, fun wọn. (Psm 33:7.)

9. Iwọ ti pa ààlà kan ki wọn má le kọja rẹ; ki wọn má tun pada lati bo ayé mọlẹ. (Job 38:10,11; Jer 5:22.)

**Awọn orisun-omi ni afonifoji.**

10. Iwọ ran orisun si afonifoji, ti nṣan laarin awọn òkè. (Psm 107:35.)

11. Awọn ni nfi omi mimu fun gbogbo ẹranko igbẹ: awọn kẹtẹkẹtẹ igbẹ npa ounjẹ wọn. (Job 39:5.)

12. Lẹba wọn ni awọn ẹyẹ oju-ọrun yoo ni ilé wọn, ti nkọrin laarin èka igi. (Matt 38:20.)

13. O nbomi rin awọn òkè lati iyẹwù rẹ wá: èrè iṣẹ ọwọ rẹ tẹ ayé lọrùn. (Psm 65:9; 147:8.)

**Ilẹ nmu èso jade wá.**

14. O mú koriko dàgbà fun ẹran, ati ewébẹ fun ilò eniyan: ki o le maa mu ounjẹ jade lati ilẹ wá. (Psm 147:8; Job 38:27; Gen 1:29; Job 23:5.)

15. Ati ọti-waini ti nmu inu eniyan dùn, ati òróró ti nmu ojú rẹ̀ dán, ati ounjẹ ti nmu eniyan ni àyà le. (Ondj 9:13; Psm 23:5.)

16. Igi Oluwa kun fun òje, igi kedari Labanoni, ti o tì gbìn.

17. Nibi ti awọn ẹyẹ ntẹ ìtẹ́ wọn: bi o ṣe ti àkọ̀ ni, igi firi ni ilé rẹ̀.

18. Awọn òkè giga ni ààbò fun awọn ewurẹ ìgbẹ́: ati awọn apata fun awọn ehoro. (Owe 30:26.)

**Oṣupa ati oorun.**

19. O da òṣupá fun àkókò: oorun mọ àkókò iwọ rẹ̀. (Gen 1:14.)

20. Iwọ ṣe okunkun ó sì di òru: ninu eyi ti gbogbo ẹranko igbó nrin kiri. (Isa 45:7.)

21. Awọn ẹgbọrọ kinniun ndún si ohùn ọdẹ wọn, wọn si nwa ounjẹ wọn lọwọ Ọlọrun. (Job 38:39.)

22. Òòrùn la, wọn kó ara jọ, wọn dubulẹ ninu ihò wọn.

23. Eniyan jade lọ si iṣẹ́ rẹ̀ ati si laalaa rẹ̀ titi di aṣalẹ. (Gen 3:19.)

24. Oluwa, iṣẹ́ rẹ ti pọ tó! ninu ọgbọ́n ni Iwọ ṣe gbogbo wọn: ayé kun fun ẹ̀dá rẹ. (Psm 40:5; Owe 3:19; Psm 65:9.)

25. Bẹẹ ni okun yìí ti ọ tobi, ti o si ni ìbú, nibẹ ni ohun ainiye nrákó, ati ẹran kekere ati nla wà.

26. Nibẹ ni ọkọ̀-ojuomi nrin: nibẹ ni Lefiatani wa, ti iwọ dá lati maa ṣe àríyá ninu rẹ̀. (Psm 107:23; Job 41:1.)

**Ọlọrun orisun ìyè.**

27. Gbogbo wọnyìí ni o duro ti ọ; ki iwọ le maa fun wọn ni ounjẹ wọn ni àkókò wọn. (Psm 136:25; 145:15.)

28. Eyi ti iwọ fi fun wọn ni wọn nkó: iwọ ṣi ọwọ́ rẹ, a si fi ohun rere tẹ wọn lọ́rùn.

29. Iwọ pa ojú rẹ mọ́, ara ko rọ̀ wọn: iwọ gba ẹmi wọn, wọn kú, wọn si pada si erupẹ wọn. (Job 34:14; Psm 146:4; Onws 12:7.)

30. Iwọ rán ẹmi rẹ jade, a si da wọn: iwọ si sọ ojú ilẹ̀ di ọ̀tun. (Isa 32:15; Esk 37:9.)

**Ìyìn ni fun Ọlọrun alagbara.**

31. Ogo Oluwa yoo wà laelae: Oluwa yoo yọ̀ ni iṣẹ́ ọwọ́ rẹ̀. (Gen 1:31.)

32. O bojuwo ayé, o si wa-riri: o fi ọwọ́ kan òkè, wọn si rú eefin. (Psm 97:4,5; 144:5.)

33. Emi o maa kọrin si Oluwa nigba ti mo wà láàyè: emi o maa kọrin ìyìn si Ọlọrun mi ni igba ayé mi. (Psm 63:4; 146:2.)

34. Jẹ ki àṣàrò mi o mu inu rẹ̀ dun: emi o maa yọ̀ ninu Oluwa.

35. Jẹ ki awọn ẹlẹṣẹ run kuro ni ayé, ki awọn eniyan buburu má si mọ́. Fi ibukun fun Oluwa, ìwọ ọkàn mi. Ẹ fi ìyìn fun Oluwa. (Psm 59:13; 37:10; ẹsẹ 1.)

## ORIN 105.

**Ìpè lati dupẹ lọwọ Ọlọrun.**

EFI ọpẹ fun Oluwa? Ẹ pe orukọ rẹ̀: ẹ fi iṣẹ́ rẹ̀ hàn ninu awọn eniyan. (1 Kro 16:8; Psm 145:12.)

2. Ẹ kọrin si i, ẹ kọ orin mímọ́ si i: ẹ maa sọ̀rọ̀ iṣẹ́ iyanu rẹ gbogbo. (Psm 77:12.)

3. Ẹ maa ṣogo ni orukọ rẹ mímọ́; jẹ ki àyà awọn ti nwa Oluwa yọ̀. (Psm 33:21.)

4. Ẹ maa wá Oluwa ati ipá rẹ̀: ẹ maa wa ojú rẹ̀ nigbagbogbo. (Psm 27:8.)

5. Ẹ maa ranti iṣẹ́ iyanu rẹ̀ ti o ti ṣe; iṣẹ́ àmì rẹ̀ ati idajọ ẹnu rẹ̀. (Psm 77:11.)

6. Ẹyin irú-ọmọ Abrahamu iranṣẹ rẹ̀, ẹ̀yin ọmọ Jakọbu, ayanfẹ rẹ̀!

**Majẹmu Abrahamu.**

7. Oluwa, oun ni Ọlọrun wa: idajọ rẹ nbẹ ni gbogbo ayé. (Isa 26:9.)

8. O ti ranti majẹmu rẹ̀ laelae, ọ̀rọ̀ ti o ti pa ni àṣẹ fun ẹgbẹrun ìran. (Luk 1:72.)

9. Majẹmu ti o ba Abrahamu dá, ati ibura rẹ̀ fun Isaaki. (Gen 17:2; 22:16; 26:3.)

10. O si gbé èyí naa kalẹ ni ọfin fun Jakọbu, ati fun Israẹli ni majẹmu ayérayé. (Gen 28:13-15.)

11. Pé, "Iwọ ni emi o fi ilẹ Kenaani fun, ìpín ilẹ-ìní yin." (Gen 13:15; 15:18.)

12. Nigba ti o ṣe pe diẹ ni wọn jẹ ni iye; nitootọ, wọn mọ ni iwọn alejo si ni wọn ninu rẹ. (Gen 34:5; Deut 7:7; Heb 11:9.)

13. Nigba naa ni wọn nlọ lati orilẹ-èdè kan dè èkeji, lati ijọba kan dé ọ̀dọ̀ awọn eniyan mìràn.

14. Oun ko jẹ ki ẹnikẹni ṣe wọn ni ìwọ̀sí: Nitootọ, o ba awọn ọba wí nitori wọn. (Gen 35:5; 12:17.)

15. Pe, "Ẹ máṣe fi ọwọ́ kan ẹni-àmì òróró mi ki ẹ má ṣe awọn woli mi ni ibi."

**Ọlọrun ran Josẹfu si Egipti.**

16. Pẹlupẹlu ó pe ìyàn wá si ilẹ naa: ó ṣẹ́ gbogbo ọ̀pá ounjẹ. (Gen 41:54; Lef 26:26; Isa 3:1; Esk 4:16.)

17. O rán ọkunrin kan lọ siwaju wọn; ani Josẹfu ti a tà ni ẹrú. (Gen 45:5; 37:28,36.)

18. Ẹsẹ̀ ẹni ti wọn fi ṣẹ́kẹ́ṣẹkẹ̀ pa lara; a de e ninu irin. (Gen 39:20.)

19. Titi igba ti ọ̀rọ̀ rẹ̀ de: ọ̀rọ̀ Oluwa dan an wò. (Gen 40:20,21; Psm 66:10.)

20. Ọba ranṣẹ, wọn si tu u silẹ; ani ijoye awọn eniyan, o si fi í silẹ lati lọ. (Gen 41:14.)

21. O fi jẹ oluwa ile rẹ̀, ati ijoye gbogbo ìní rẹ̀. (Gen 41:40.)

22. Lati maa ṣe akoso awọn ọmọ-alade rẹ̀ nipa ìfẹ́ rẹ̀; ati lati maa kọ́ awọn igbimọ rẹ̀ ni ọgbọ́n.

**Israẹli ni Egipti.**

23. Israẹli si wa si Egipti pẹlu; Jakọbu si ṣe àtìpó ni ilẹ̀ Hamu. (Gen. 46:6; A.A. 13:17.)

24. O si mu awọn eniyan rẹ̀ bi si i pupọ-pupọ; o si mu wọn lagbara ju awọn ọtá wọn lọ. (Eks 1:7.)

25. O yi wọn ni àyà pada lati korira awọn eniyan rẹ̀, lati ṣe arekereke si awọn iranṣẹ rẹ̀. (Eks 1:8,10.)

**Mose ati iṣẹ́ iyanu Ọlọrun.**

26. O rán Mose iranṣẹ rẹ̀; ati Aarọni ẹni ti o ti yàn. (Eks 3:10; Num 16:5.)

27. Wọn fi ọ̀rọ̀ àmì rẹ̀ hàn ninu wọn, ati iṣẹ́ iyanu ni ilẹ̀ Hamu. (Eks ori 7–12; Psm 78:43.)

28. O rán okunkun, o si mu un ṣú; wọn ko si gbọran si ọ̀rọ̀ rẹ̀. (Eks 10:22; Psm 99:7.)

29. O sọ omi wọn di ẹ̀jẹ̀, o si pa ẹja wọn. (Eks 7:20.)

30. Ilẹ wọn kún fún ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ ọ̀pọ̀lọ́, paapaa ninu iyara awọn ọba wọn. (Eks 8:6.)

31. Ó sọ̀rọ̀, oniruuru eṣinṣin si de, ati iná-aṣọ ni gbogbo agbegbe wọn. (Eks 8:16,21.)

32. O fi yìnyín fun wọn fun òjò, ọwọ́ iná ni ilẹ wọn. (Eks 9:23.)

33. O si lu àjàrà wọn, ati igi-ọ̀pọ̀tọ́ wọn; o si dá igi agbegbe wọn.

34. O sọ̀rọ̀, eeṣú si dé ati kokoro ni ainiye. (Eks 10:4; Psm 78:46.)

35. Wọn si jẹ gbogbo ewébẹ̀ ilẹ wọn, wọn si jẹ èsó ilẹ wọn run.

36. O kọlu gbogbo akọbí pẹlu ni ilẹ̀ wọn, ààyò gbogbo ipá wọn. (Eks 12:29; Psm 78:51.)

**Jijade kuro ni Egipti.**

37. O si mu wọn jade, ti awọn ti fadaka ati wura: kò si sí alailera kan ninu ẹ̀yà rẹ̀. (Eks 12:35.)

38. Inu Egipti dùn nigba ti wọn lọ: nitori ti ẹ̀rù wọn ba wọn. (Eks 12:33.)

39. O nà awọsanma kan fun ìbòrí; ati iná lati fun wọn ni ìmọ́lẹ̀ ni òru. (Eks 13:21; Neh 9:12.)

40. Wọn beere o si mu ẹyẹ àparò wa, o si fi ounjẹ ọ̀run tẹ́ wọn lọ́rùn. (Eks 16:12; Psm 78:24.)

41. O la apata, omi si tu jade; o si ṣan bi odo kọja ni ilẹ-gbigbẹ. (Eks 17:6; Psm 78:15,16; 1 Kro 10:4.)

42. Nitori ti o ranti ileri rẹ̀ mimọ, ati Abrahamu iranṣẹ rẹ̀. (ẹsẹ 8.)

**Ilẹ̀ ileri naa-Kenaani.**

43. O si fi ayọ̀ mu awọn eniyan rẹ̀ jade, ati awọn àyànfẹ́ rẹ̀ pẹlu orin ayọ̀:

44. O si fi ilẹ̀ awọn Keferi fun wọn: wọn si jogun èrè iṣẹ́ awọn eniyan naa. (Deut 6:10; Jer 13:7.)

45. Ki wọn le maa kiyesi aṣẹ rẹ̀, ki wọn si maa pa ofin rẹ̀ mọ́. Ẹ fi ìyìn fun Oluwa. (Deut 6:21–25.)

## ORIN 106.

**Adura fun aanu.**

EFI ìyìn fun Oluwa! Ẹ fi ọpẹ fun Oluwa: nitori ti o ṣeun: nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae. (Psm 105:1; 100:5; 1 Kro 16:34.)

2. Tani o le sọ̀rọ iṣẹ́ agbara Oluwa? Tani o le fi gbogbo ìyìn rẹ̀ hàn? (Psm 145:4,12.)

3. Ibukun ni fun awọn ti npa idajọ mọ́, ati ẹni ti nṣe ododo ni igbagbogbo. (Psm 5:1.)

4. Oluwa, fi ojú-rere ti iwọ ni si awọn eniyan rẹ ṣe iranti mi: fi igbala rẹ bẹ̀ mi wò. (Psm 119:132.)

5. Ki emi le ri ire awọn ayanfẹ rẹ, ki emi le yọ̀ ninu ayọ̀ orilẹ-èdè rẹ, ki emi le maa ṣogo pẹlu awọn eniyan ilẹ-ini rẹ. (Psm 1:3; 118:15; 105:3.)

**Ẹ̀ṣẹ̀ Israẹli ni Okun-pupa.**

6. Awa ti ṣẹ̀ pẹlu awọn baba wa, awa ti dẹṣẹ, awa ti ṣe buburu. (Dan 9:5.)

7. Iṣẹ́ iyanu rẹ kò yé awọn baba wa ni Egitpi; wọn kò ranti ọpọlọpọ aanu rẹ; ṣugbọn wọn sọ̀tẹ̀ si ọ nibi òkun, ani nibi òkun pupa. (Psm 78:11,42; Eks 14:11.)

8. Ṣugbọn o gbà wọn là nitori orukọ rẹ, ki o le mu agbara rẹ nla di mímọ̀. (Eks 9:16.)

9. Ó bá Okun pupa wí pẹlu o si gbẹ: bẹẹ ni o sìn wọn la ibú ja ni aginju. (Eks 14:21; Psm 18:15; 78:11,42; Isa 63:11–14.)

10. O si gbà wọn là ni ọwọ́ ẹni ti o korira wọn, o si rà wọn pada kúrò ni ọwọ́ ọ̀tá. (Eks 14:30; Psm 107:2.)

11. Omi si bo awọn ọ̀tá wọn; ẹnikan kò si kù. (Eks 14:28; 15:5.)

12. Nigba naa ni wọn gba ọ̀rọ̀ rẹ gbọ́: wọn si kọrin ìyìn rẹ̀. (Eks 14:31; 15:1–21.)

**Ẹ̀ṣẹ̀ Israẹli ni aginju.**

13. Wọn kò pẹ gbagbe iṣẹ́ rẹ: wọn kò si duro de ìmọ̀ rẹ̀. (Eks 15:24.)

14. Wọn si ṣe ifẹkufẹ laginju, wọn si dan Ọlọrun wò ninu aṣálẹ̀. (1 Kro 10:6,9.)

15. O si fun wọn ni ohun ti wọn bèèrè; ṣugbọn o rán àrùn-rírù si ọkàn wọn. (Num 11:31; Isa 10:16.)

**Ẹ̀ṣẹ̀ Datani ati Abiranmu.**

16. Wọn ṣe ilara Mose pẹlu ni ibùdó, ati Aarọni, ẹni-mímọ́ Oluwa. (Num 16:1–3.)

17. Ilẹ là, o si gbé Datani mì, o si bò ẹgbẹ́ Abiramu mọlẹ. (Deut 11:6.)

18. Iná si ràn ni ẹgbẹ́ wọn; ọwọ́ iná naa jó awọn eniyan buburu. (Num 16:35.)

**Èrè ẹgbọrọ-malu wura ti Horẹbu.**

19. Wọn ṣe ẹgbọrọ malu ni Horebu, wọn si foribalẹ fun ère dídá. (Eks 32:14.)

20. Bayìí ni wọn pa ogo wọn dà sí àwòrán malu ti njẹ koriko. (Jer 2:11; Rom 1:23.)

21. Wọn gbàgbé Ọlọrun, Olugbala wọn, ti o ti ṣe ohun nla ni ilẹ Egipti. (Psm 78:11; Deut 10:21.)

22. Iṣẹ́ iyanu ni ilẹ Hamu, ati ohun ẹ̀rù lẹba Òkun pupa. (Psm 105:27.)

23. Nitori naa ni o ṣe wi pe, "Oun o run wọn, iba má ṣe pé Mose, àyànfẹ́ rẹ̀, duro niwaju rẹ̀ loju-ẹ̀yà naa, lati yi ibinu rẹ̀ pada, ki o má ba run wọn. (Eks 32:10; 32:11–14.)

**Ainifẹ lati wọ ilẹ ileri.**

24. Nitootọ, wọn kọ ka ilẹ̀ didara si, wọn kò gba ọ̀rọ̀ rẹ̀ gbọ́. (Deut 8:7; Heb 3:18,19.)

25. Ṣugbọn wọn nkùn ninu àgọ́ wọn, kọ si feti si ohun Oluwa. (Num 14:2.)

26. Nitori naa ni o ṣe gbé ọwọ́ rẹ̀ soke si wọn, lati bì wọn ṣubú ni aginju. (Num 14:28–35; Heb 11:3.)

27. Lati bi iru-ọmọ wọn ṣubú pẹlu laarin awọn orilẹ-èdè, ati lati fọ́n wọn ká kiri ni ilẹ̀ naa. (Psm 44:11.)

**Baali Peori.**

28. Wọn da ara wọn pọ̀ pẹlu mọ Baali-Peoru, wọn si njẹ ẹbọ òkú. (Num 25:2,3.)

29. Bayìí ni wọn fi iṣẹ́ wọn mu un binu: àrùn nla si fò si arin wọn.

30. Nigba naa ni Finehasi dide dúró, o si ṣe idajọ: bẹẹ ni àrùn nla naa si dá. (Num 25:7.)

31. A si kà eyi naa si fun un lododo lati irandiran titi lae. (Num 25:11–13.)

**Ẹ̀ṣẹ̀ Israẹli ni Meriba.**

32. Wọn bi i ninu pẹlu nibi omi Meriba, bẹẹ ni o buru fun Mose nitori wọn. (Num 20:3,13; Psm 81:7.)

33. Nitori ti wọn mu ẹmi binu, bẹẹ ni o fi ẹnu rẹ̀ sọ ọ̀rọ̀ àìyẹ. (Num 20:10.)

34. Wọn kò run awọn orilẹ-èdè naa, ni ti ẹni ti Oluwa pàṣẹ fún wọn. (Ondj 1:21; Deut 7:2,16.)

35. Ṣugbọn wọn da ara wọn pọ̀ mọ awọn Keferi, wọn si kọ iṣẹ́ wọn. (Ondj 3:5,6.)

36. Wọn si sìn ère wọn: eyi ti o di ikẹkun fun wọn. (Odnj 2:12.)

37. Nitootọ wọn fi ọmọkunrin wọn ati ọmọbinrin wọn rubọ si oriṣa. (2 A. Ọba 17:7.)

38. Wọn si ta ẹ̀jẹ̀ alaiṣẹ silẹ, àní ẹ̀jẹ̀ awọn ọmọkunrin wọn ati ti awọn ọmọbinrin wọn, ti wọn fi rubọ si ère Kenaani: ilẹ̀ naa si di àìmọ́ fun ẹ̀jẹ̀. (Psm 94:21; Num 35:33.)

39. Wọn si fi iṣẹ ara wọn sọ ara wọn di alaìmọ́, wọn si ṣe pansaga lọ pẹlu iṣẹ́ wọn. (Esk 20:18; Lef 17:7; Num 15:39.)

**Ìjìyà ẹ̀ṣẹ̀ Israẹli.**

40. Nitori naa ni ibinu Oluwa ṣe ràn si awọn eniyan rẹ̀, o si korira awọn eniyan ìní rẹ̀. (Psm 78:59.)

41. O si fi wọn le awọn Keferi lọwọ; awọn ti o korira wọn si ṣe olori wọn. (Ondj 2:14; Neh 9:27.)

42. Awọn ọ̀tá wọn si ni wọn lara, wọn si mu wọn sìn labẹ ọwọ́ wọn.

43. Ìgbà pupọ ni o gbà wọn; síbẹ̀ wọn fi ìmọ̀ wọn mu un binu, a si rẹ̀ wọn silẹ nitori ẹ̀ṣẹ̀ wọn. (Ondj 2:16–18.)

**Aanu Ọlọrun.**

44. Ṣugbọn ninu ipọnju o kiyesi wọn, nigba ti o gbọ́ ẹkún wọn. (Ondj 3:9; 10:10.)

45. O si ranti majẹmu rẹ̀ fun wọn, o si yi ọkàn pada gẹgẹ bi ọpọlọpọ aanu rẹ̀. (Psm 105:8; Ondj 2:18.)

46. O si mu wọn ri aanu loju gbogbo awọn ti o kó wọn ni ìgbèkùn. (Esra 9:9; Jer 42:12.)

**Ìpè ikẹhin sí Ọlọrun.**

47. Oluwa Ọlọrun wa, gba wa, ki o si ṣà wa jọ kuro laarin awọn keferi, lati maa fi ọpẹ́ fún orukọ mímọ́ rẹ, ati lati maa ṣogo ninu iyin rẹ. (1 Kro 16:35; 36; Psm 147:2.)

48. Olubukun ni Oluwa, Ọlọrun Israẹli, lati ayérayé; ki gbogbo eniyan si maa wi pe, "Amin". Ẹ fi ìyìn fún Oluwa! (Psm 41:13.)

## IWE KARUN

## ORIN 107.

**Ìpè si ìyìn fun Ọlọrun.**

EFI ọpẹ́ fun Oluwa, nitori ti o ṣeun: nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae. ( Psm 106:1.)

2. Jẹ ki awọn ẹni-ìràpadà Oluwa wi bẹẹ, ẹni ti o rà pada kuro lọwọ ọ̀tá. (Psm 106:10.)

3. O si kó wọn jọ lati awọn ilẹ̀ naa wá, lati ila-oorun wá, ati lati iwọ-oorun, lati ariwa, ati lati òkun wá. (Psm 106:47; Isa 43:5,6.)

**Idande kuro ni aginju.**

4. Wọn nrin kakiri ni aginju ni ibi ti ọna kò si: wọn kò ri ilu lati maa gbe. (Num 14:33; 32:13.)

5. Ebi pa wọn, oungbẹ si gbẹ wọn, ó rẹ ọkàn wọn ninu wọn.

6. Nigba naa ni wọn kígbe pe Oluwa ninu ipọnju wọn, o si yọ wọn kuro ninu ìṣẹ́ wọn. (Psm 50:15.)

7. O si mu wọn jade nipa ọ̀nà titọ, ki wọn le lọ si ìlú ti wọn o maa gbé. (Esra 8:21.)

8. Eniyan iba maa yin Oluwa nitori oore rẹ̀, ati nitori iṣẹ́ iyanu rẹ̀ si awọn ọmọ eniyan.

9. Nitori ti o tẹ iṣẹ́ ọkàn lọrun, o si fi ire kún ọkàn ti ebi npa. (Psm 22:25; Luk 1:53.)

**Idande kuro ninu ìgbèkùn.**

10. Irú awọn ti o jókòó lokunkun ati ni ojiji ikú, ìgbèkùn ninu ipọnju ati ni irin. (Luk 1:79; Job 36:8.)

11. Nitori ti wọn ṣọ̀tẹ̀ sí ọ̀rọ̀ Ọlọrun, wọn si gan ìmọ̀ Ọga-ogo. (Psm 106:7; 2 Kro 36:16.)

12. Nitori naa o fi làálàá rẹ̀ àyà wọn silẹ: wọn ṣubú, kò sì si oluranlọwọ. (Psm 22:11.)

13. Nigba naa ni wọn kigbe pe Oluwa ninu ipọnju wọn, o si gba wọn ninu ìṣẹ́ wọn. (ẹsẹ 6.)

14. O mu wọn jade kuro ninu òkùnkùn ati ojiji ikú, o si fa ìdè wọn já. (Psm 116:16; Luk 13:16; A.A. 12: 7.)

15. Eniyan ìbá maa yin Oluwa: nitori ore rẹ̀, ati nitori iṣẹ́ iyanu rẹ̀ si awọn ọmọ eniyan. (ẹsẹ 8:21,31.)

16. Nitori ti o fọ́ awọn ilẹkun idẹ, o si ge awọn ọ̀pá-idabu irin lagbedemeji. (Isa 45:2.)

**Idande kuro ninu aisan.**

17. Aṣiwere (òmùgọ̀) nitori irekọja wọn, ati nitori ẹ̀ṣẹ̀ wọn, ojú npọn wọn. (Isa 65:6,7.)

18. Ọkàn wọn kọ ounjẹ-kounjẹ; wọn si súnmọ́ etí ẹnu-ọ̀nà ikú. (Job 33:20; 22; Psm 9:13; 88:3.)

19. Nigba naa ni wọn kigbe pe Oluwa ninu ipọnju wọn, ó si gba wọn ninu ìṣẹ́ wọn.

20. O rán ọ̀rọ̀ rẹ̀, o mu wọn lara dá, o si gba wọn kuro ninu iparun wọn. (Matt 8:8; Psm 30:2; 103:3.)

21. Eniyan ìbá maa yin Oluwa nitori oore rẹ̀, ati nitori iṣẹ́ iyanu rẹ̀ si awọn ọmọ eniyan.

22. Si jẹ ki wọn rú ẹbọ ọpẹ, ki wọn si fi orin ayọ̀ sọrọ iṣẹ́ rẹ̀. (Lef 7:12; Psm 50:14; 9:11; 73:28; 118:17.)

**Idande kuro ninu iparun ninu òkun.**

23. Awọn ti nsọkalẹ lọ si òkun ninu ọkọ̀-ojuomi ti nṣiṣẹ ninu omi nla.

24. Awọn wọnyii ri iṣẹ́ Oluwa, ati iṣẹ́-iyanu rẹ̀ ninu ibú.

25. Nitori ti o paṣẹ, o si mu ìjì fẹ́, ti o gbé riru rẹ̀ sókè. (Psm 105:31,34; Jon 1:4; O.D 93:3,4.)

26. Wọn gòkè lọ si ọ̀run, wọn si tun sọkalẹ lọ si ibú; ọkàn wọn di omi nitori ipọnju. (Psm 22:14; 119:28.)

27. Wọn nta gbọ̀n-ọ́ngbọn-ọ́n sihin sọhun, wọn nta gbọn-ọngbọn-ọ́n bi ọmuti eniyan, ọgbọn wọn sí de opin. (Job 12:25.)

28. Nigba naa ni wọn kigbe pe Oluwa ninu ipọnju wọn, o si yọ wọn kuro ninu ìṣẹ́ wọn. (ẹsẹ 6:13,19.)

29. O sọ ìjì di ìdakẹ-rọ́rọ́, bẹẹ ni rírú omi rẹ̀ duro jẹ. (Psm 89:9; Matt 8:26.)

30. Nigba naa ni wọn yọ̀, nitori ti ara wọn balẹ; bẹẹ ni o mu wọn wa si ebute ifẹ wọn.

31. Eniyan iba maa yin Oluwa nitori oore rẹ̀, ati nitori iṣẹ́ iyanu rẹ̀ si awọn ọmọ eniyan. (ẹsẹ 8,15,21.)

32. Ki wọn gbe e ga pẹlu ni ìjọ eniyan, ki wọn si yin in ninu ìjọ awọn àgbà. (Psm 22:22, 25; 35:18.)

**Oluwa ti o bukun fun ilẹ-ayé.**

33. O sọ odò di aginju, ati orisun omi di ilẹ̀ gbigbẹ. (Psm 74:15.)

34. Ilẹ eleso di aṣálẹ̀, nitori ìwà-buburu awọn ti o wa ninu rẹ. (Gen 13:10; 14:3; 19:25.)

35. O sọ aginju di adagun omi, ati ilẹ̀ gbigbẹ di orisun omi. (Psm 114:8; Isa 41:18.)

36. Nibẹ ni o si mu awọn ti ebi npa jókòó, ki wọn le tẹ ilu dó, lati maa gbé.

37. Lati fọ́n irúgbìn si oko, ki wọn si gbìn agbala àjàrà, ti yoo maa so eso ọ̀pọ̀lọpọ̀. (Isa 65:21.)

38. O busi i fun wọn pẹlu, bẹẹ ni wọn si pọ̀ si i gidigidi; kò si jẹ ki ẹranọ̀sìn wọn fà sẹhin. (Gen 12:2; 17:16, 20; Eks 1:7.)

**Ìfẹ́ Ọlọrun ti o jinlẹ.**

39. Ẹwẹ̀, wọn bùkú, wọn si fa sẹ́hìn, nipa inira, ipọnju, ati ìkaanu. (Esk 5:11; Psm 57:6.)

40. Ó da ẹ̀gàn lu awọn ọmọ-alade, o si mu wọn rin kiri ni ijù, nibi ti ọ̀nà kò sí. (Job 12:21,24.)

41. Sibẹ o gbe talaka lékè kuro ninu ipọnju, o si ṣe awọn idile wọn bi agbo-ẹran. (1 Sam 2:8; Psm 113:7–9.)

42. Awọn ẹni iduro-ṣinṣin yoo ri i, wọn o si yọ̀: gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ ni yoo si pa ẹnu rẹ̀ mọ́. (Job 22:19; Psm 52:6; Job 5:16; Rom 3:19; Psm 63:11.)

43. Ẹni ti o gbọ́n, yoo si kiyesi nkan wọnyìí; awọn naa ni òye iṣeun-ifẹ Oluwa yoo maa yé. (Psm 64:9; Jer 9:12; Hos 14:9.)

## ORIN 108.

**Ọpẹ́ fun Ọlọrun.**

OLỌRUN, ọkàn mi ti mura, emi o maa kọrin, emi o si maa fi ogo mi kọrin ìyìn. (Psm 57:7.)

2. Jí ohun-elo orin mímọ́ ati dùùrù; emi tikarami yoo si ji ni kutukutu! (Psm 57:8–11.)

3. Emi o maa yin ọ, Oluwa, ninu awọn eniyan: emi o maa kọrin si ọ ninu awọn orilẹ-ede.

4. Nitori ti aanu rẹ tobi ju ọ̀run lọ: ati otitọ rẹ titi de awọsanma. (Psm 113:4.)

5. Gbe ara rẹ ga, Ọlọrun, lori awọn ọrun; ati ogo rẹ lori gbogbo ayé.

**Ẹ̀bẹ̀ fun ileri Ọlọrun.**

6. Ki a le gba awọn olufẹ rẹ là: fi ọwọ́ ọ̀tún rẹ ṣe igbala, ki o si da mi lóhùn. (Psm 60:5–12.)

7. Ọlọrun ti sọ ninu ìwà-mímọ́ rẹ̀ pé; "Emi o yọ̀, emi o pin Ṣekemu, emi o si wọn afonifoji Sukkotu.

8. Ti emi ni Gileadi; ti emi ni Manasse; Efraimu ni agbára orí mi: Juda ni olofin mi. (Psm 60:7.)

9. Moabu ni ìkòkò-ìwẹṣẹ̀ mi; lori Edomu ni emi o bọ bata mi sí; lori Filistini ni emi yoo hó ìhó-ayọ̀."

**Ìpè fun iranlọwọ.**

10. Tani yoo mu mi wa sinu ilu olodi nì? Tani yoo sin mi lọ si Edomu?

11. Iwọ Ọlọrun ha kọ́ ni, ti o ti ṣa wa tì? Ọlọrun, iwọ ki yoo si ba awọn ogun wa jade lọ? (Psm 44:9.)

12. Fun wa ni iranlọwọ ninu ipọnju: nitori asán ni iranlọwọ eniyan.

13. Nipasẹ Ọlọrun lawa o ṣe akin: nitori oun ni yoo tẹ awọn ọta wa mọ́lẹ̀.

## ORIN 109.

**Ìpè si Ọlọrun fun aanu.**

MA ṣe pa ẹnu rẹ mọ, Ọlọrun ìyìn mi. (Psm 83:1.)

2. Nitori ti ẹnu awọn eniyan buburu, ati ẹnu awọn ẹlẹtan yà silẹ si mi: wọn ti fi ahọ́n èké sọ̀rọ̀ si mi. (Psm 52:4; 120:2.)

3. Wọn si fi ọ̀rọ̀ irira yi mi ka kiri; wọn si nba mi jà ni ainidi. (Psm 69:4.)

4. Nipo ifẹ́ mi wọn nṣe ọ̀tá mi: ṣugbọn emi ngba adura. (Psm 38:20; 69:13.)

5. Wọn si fi ibi san ire fun mi, ati irira fun ifẹ́ mi. (Psm 35:12; 38:20.)

**Ègún.**

6. Yan eniyan buburu ti i: jẹ ki Olùfisùn duro lọwọ ọ̀tún rẹ̀. (Sek 3:1.)

7. Nigba ti a o ṣe idajọ rẹ̀, ki a da a lẹbi; ki adura rẹ̀ di ẹ̀ṣẹ̀. (Owe 28:9.)

8. Ki ọjọ́ rẹ̀ kúrú; ki ẹlomiran rọ́pò iṣẹ́ rẹ̀! (A.A. 1:20.)

9. Ki awọn ọmọ rẹ̀ di alaini-baba, ki aya rẹ̀ di opó! (Eks 22:24.)

10. Jẹ ki awọn ọmọ rẹ di alarinkiri, ti nṣagbe: ki wọn maa tọrọ ounjẹ jinna si ibi ahoro wọn.

11. Jẹ ki alọnilọwọ-gba mu ohun gbogbo ti o ni; ki alejo kó èrè-iṣẹ rẹ lọ. (Job 5:5; 18:9.)

12. Ki ẹnikẹni má si lati ṣaanu fun un: ma si ṣe jẹ ki ẹnikẹni si lati ṣe ojú rere fun awọn ọmọ rẹ alaini-baba! (Isa 9:17.)

13. Ki a ge ati ọmọde ọmọ rẹ kúrò? Ati ni iran ti nbọ ki orukọ wọn parẹ. (Psm 37:28; Owe 10:7.)

14. Ki a maa ranti ẹṣẹ awọn baba rẹ lọdọ Oluwa; ma si jẹ ki a nu ẹṣẹ iyá rẹ nù! (Eks 20:5; Neh 4:5; Jer 18:23.)

15. Jẹ ki wọn wà niwaju Oluwa nigbagbogbo, ki iranti wọn gé kuro lori ilẹ! (Psm 34:16.)

16. Nitori ti kò ranti ṣaanu, ṣugbọn o ṣe inunibini si ọkunrin talaka ati olupọnju, ki o le pá oniro-binujẹ-ọkàn. (Psm 37:14,32.)

17. Bi o ti fẹ ègún, bẹẹ ni ki o de si i, bi inu rẹ ko ti dùn si ire, bẹẹ ni ki o jinna si i. (Owe 14:14; Esk 35:6.)

18. Bi o ti fi ègún wọ ara rẹ laṣọ bi ẹwù rẹ, bẹẹ ni ki o wà si inu rẹ bi omi, ati bi òróró sinu egungun rẹ! (Psm 73:6; Num 5:22.)

19. Jẹ ki o ri fun un bi aṣọ ti o bo o lára, ati fun àmùrè ti o fi gbàjá nigbagbogbo.

20. Eyi ni èrè awọn ọtá mi lati ọwọ Oluwa, wa, ati ti awọn ti nsọrọ ibi si ọkàn mi! (Psm 94:23; 2 Tim 4:14; Psm 71:10.)

**Ìpè si Ọlọrun ntẹsiwaju.**

21. Ṣugbọn iwọ ṣe fun mi, Ọlọrun Oluwa, nitori orukọ rẹ: nitori ti aanu rẹ dara, ìwọ gbà mi. (Psm 79:9; 69:16.)

22. Nitori pé talaka ati olupọnju ni emi, àyà mi si gbọgbẹ ninu mi. (Psm 40:17; 143:4.)

23. Emi nkọja lọ bi ojiji ti o nfà sẹhin, emi nti soke ti sódò bi eeṣú. (Psm 102:11.)

24. Eekun mi di ailera nitori ìgbàawẹ; ẹran-ara mi si gbẹ nitori ailera. (Heb 12:12.)

25. Emi di ègàn fun wọn pẹlu: nigba ti wọn wò mi, wọn mi ori wọn. (Psm 22:6,7; Matt 27:39; Mk 15:29.)

26. Ràn mi lọwọ, Oluwa Ọlọrun mi: gbà mi gẹgẹ bi aanu rẹ. (Psm 11:86.)

27. Ki wọn le mọ pé ọwọ rẹ ni èyí; pé Iwọ, Oluwa, ni o ṣe e. (Job 37:7.)

28. Wọn o maa gegun, ṣugbọn iwọ maa sure; nigba ti wọn bá dide, ki ojú ti wọn; ṣugbọn iranṣẹ rẹ yọo yọ. (2 Sam 16:11,12; Isa 65:14.)

29. Jẹ ki a fi ìtìjú wọ awọn ọtá mi laṣọ, ki wọn si fi idarudapọ wọn bo ara, bi ẹni pe ẹwù. (Psm 35:26; 132:18.)

30. Emi o maa fi ẹnu mi yin Oluwa gidigidi; nitootọ, emi o maa yin in laarin ọpọ eniyan. (Psm 35:18.)

31. Nitori ti yoo duro ni ọwọ ọtún olupọnju, lati gba a lọwọ awọn ti o ndá ọkàn rẹ lẹbi. (Psm 16:8; 121:5.)

## ORIN 110.

**Messiah Ọba.**

JEHOFAH wi fun Oluwa mi pé, Iwọ jókòó lọwọ ọtún mi, titi emi o fi sọ awọn ọtá rẹ di apoti-itisẹ rẹ. (Matt 22:44; Mk 12:36; Luk 20:42; A.A. 2:34; 1 Kor 15:25.)

2. Oluwa yoo na ọpá agbara rẹ lati Sioni wá: iwọ jọba laarin awọn ọtá rẹ. (Psm 45:6; 2:9; A.A. 1–4.)

**Messiah Alufa Ọga-ogo.**

3. Awọn eniyan rẹ jẹ ọrẹ atinuwa ni ọjọ ijade-Ogun rẹ, ninu ẹwà iwa-mímọ́: lati inu owurọ wá, iwọ ni ìrì ewe rẹ. (Ondj 5:2; Psm 96:9.)

4. Oluwa ti bura, ki yoo si yi ọkàn pada pé, Iwọ ni alufa titi lae ni tìtẹlé àpẹẹrẹ ti Melkisedeki. (Heb 5:6,10; 6:20; 7:11; 15:21.)

5. Oluwa ni ọwọ ọtun rẹ ni yoo lu awọn ọba jálẹ ni ọjọ ibinu rẹ. (Psm 16:8; 2:5–12; Rom 2:5; Ifh 11:18.)

**Messiah Aṣẹgun.**

6. Yoo ṣe idajọ laarin awọn orilẹ-ede, yoo fi òkú kún ibi wọnyìí; yoo fọ́n awọn olórí ka si ori ilẹ ayé ti o gbòòrò. (Isa 2:4; 66:24; Psm 68:21.)

7. Yoo maa mu ninu odò ṇaa, ni ọ̀nà: nitori naa ni yoo ṣe gbé orí soke. (Psm 27:6.)

## ORIN 111.

**Ìpè si ìyìn.**

Emaa yin Oluwa, Emi o maa yin Oluwa tinutinu mi, ninu ijọ awọn ẹni iduro-ṣinṣin, ati ni ijọ eniyan. (Psm 138:1; 149:1.)

**Awọn ìdí pataki ti a fi ni lati yin Oluwa.**

2. Iṣẹ́ Oluwa tobi, ìwá-kiri ni fun gbogbo awọn ti o ni ifẹ rẹ̀ ninu. (Psm 92:5.)

3. Iṣẹ́ rẹ̀ ni ọlá ati ogo, ododo rẹ̀ si duro laelae. (Psm 145:5.)

4. O ṣe iṣẹ́ iyanu rẹ̀ ni iranti: oloore-ọfẹ ni Oluwa o si kun fun aanu. (Psm 86:5; 103:8.)

5. O ti fi ounjẹ fun awọn ti o bẹ̀rù rẹ̀: yoo ranti majẹmu rẹ̀ laelae. (Matt 6:26, 33.)

6. O ti fi iṣẹ́ agbara rẹ̀ hàn awọn eniyan rẹ̀, ki o le fun wọn ni ilẹ-ìní awọn Keferi.

7. Otitọ ati idajọ ni iṣẹ́ ọwọ́ rẹ̀; gbogbo òfin rẹ̀ ni o daniloju. (Ifh 15:3; Psm 19:7.)

8. Wọn duro lae, ati laelae, ninu otitọ ati iduro-ṣinṣin ni a ṣe wọ́n. (Matt 5:18; Psm 19:9.)

9. O rán idande sí awọn eniyan rẹ̀: o ti pàṣẹ majẹmu rẹ̀ laelae: mímọ́ ati ọ̀wọ̀ ni orukọ rẹ! (Luk 1:68; Psm 99:3.)

**Ìbẹ̀rù Oluwa ni ìpilẹ̀ṣẹ̀ ọgbọ́n.**

10. Ibẹru Oluwa ni ipilẹ̀ṣẹ̀ ọgbọ́n: òye rere ni gbogbo awọn ti npa òfin rẹ̀ mọ ní: ìyìn rẹ̀ duro laelae. (Owe 9:10; 3:4; Psm 145:2.)

## ORIN 112.

**Èrè jíjẹ́ olododo.**

Emaa yin Oluwa. Ibukun ni fun ẹni ti o bẹ̀rù Oluwa, ti inu rẹ̀ dùn jọjọ ni ofin rẹ̀! (Psm 128:1; 119:16.)

2. Irú-ọmọ rẹ̀ yoo lagbara ni ayé: iran ẹni-iduro-ṣinṣin ni a o bukun fun. (Psm 25:13.)

3. Ọla ati ọrọ̀ yoo wa ni ilé rẹ̀: ododo rẹ̀ si duro laelae. (Owe 3:16; 8:18.)

4. Fun ẹni-iduro-ṣinṣin ni ìmọ́lẹ̀ mọ́ ni òkùnkùn: olore-ọ̀fẹ́, o si kùn fun aanu, o si ṣe olododo. (Job 11:17; Psm 97:11.)

5. Eniyan rere fi oju-rere hàn, a si maa tọrẹ: ìmòye ni yoo maa fi là ọ̀nà iṣẹ́ rẹ̀. (Psm 37:26.)

6. Nitori ti a ki yoo yi i nípò laelae: olódodo yoo wà ni iranti titi lae. (Owe 10:7.)

7. Ki yoo bẹru ihin buburu: àyà rẹ ti mu ọ̀nà kan, o gbẹkẹlẹ Oluwa. (Owe 1:33; Psm 57:7.)

8. Àyà rẹ̀ ti múlẹ̀, ki yoo bẹ̀rù, titi yoo fi ri ìfẹ́ rẹ̀ lori awọn ọta rẹ̀. (Psm 59:10; 118:7.)

9. O ti pín ká, o ti fi fun awọn olupọnju; ododo rẹ̀ duro laelae; ọla ni a o fi gbé ìwo rẹ̀ ga. (2 Kor 9:9; Deut 24:13; Psm 75:10.)

10. Awọn eniyan buburu yoo ri i, inu wọn o si bàjẹ́; yoo pa ehín rẹ̀ keke, yoo si yọ́ dànù: ifẹ awọn eniyan buburu yoo ṣègbé. (Psm 86:17; 37:12; 58:7,8; Owe 10:28; 11:7.)

## ORIN 113.

**Orin ìyìn si Ọlọrun.**

Emaa yin Oluwa! Ẹ maa yin, ẹyin iranṣẹ Oluwa, ẹ maa yin orukọ Oluwa. (Psm 135:1.)

2. Ibukun ni orukọ Oluwa lati isinsinyìí lọ ati titi laelae. (Dan 2:20.)

3. Lati ila-oorun titi o fi dé ìwọ̀ rẹ̀ orukọ Oluwa ni ki a yin. (Psm 50:1.)

4. Oluwa ga lori gbogbo orilẹ-èdè,

ogo rẹ̀ si wa lori ọ̀run. (Psm 97:9; 99:2; 8:1.)

5. Tani o dabi Oluwa Ọlọrun wa, ti o ngbe ibi giga. (Psm 89:6; 103:19.)

6. Ẹni ti o rẹ ara rẹ̀ silẹ̀ lati wo ohun ti o wa ni ọ̀run ati ni ayé. (Psm 11:4; 138:6; Isa 57:15.)

7. O gbé talaka soke lati inu erupẹ wá, o si gbé olupọnju soke lati ori ààtàn wá. (1 Sam 2:8; Psm 107:41.)

8. Ki o le mu un jókòó pẹlu awọn ọmọ-alade, ani pẹlu awọn ọmọ-alade awọn eniyan rẹ̀. (Job 36:7.)

9. O mu àgàn obinrin gbe inu ile, lati maa ṣe oninu-didun ìyá, awọn ọmọ, Ẹ maa yin Oluwa. (1 Sam 2:5; Psm 68:6; Isa 54:1.)

## ORÌN 114.

**Ni iranti Ọlọrun ti ngbani.**

NIGBA ti Israẹli jade kuro ni Egipti, ti ara-ile Jakọbu kuro ninu àjèjì èdè eniyan. (Eks 13:3.)

2. Juda ni ibi mimọ rẹ̀, Israẹli ni ijọba rẹ̀. (Eks 19:6; 29:45–46.)

3. Okun ri i, o si sá: Jordani pada sẹhin. (Eks 14:21; Jos 3:13, 16.)

4. Awọn òkè nla nfo bi àgbò, ati awọn òkè kekeke bi ọ̀dọ́-agutan. (Psm 29:6; Hab 3:6.)

5. Kinni ṣe ọ, iwọ òkun, ti iwọ fi sá? Ìwọ Jordani ti iwọ fi pada sẹhin? (Hab 3:8.)

6. Ẹyin òkè nla, ti ẹ fi nfo bi àgbò; ati ẹyin òkè kekeke bi ọdọ-agutan?

7. Wárìrì, iwọ ilẹ̀, niwaju Oluwa niwaju Ọlọrun Jakọbu. (Psm 96:9.)

8. Ẹni ti ó sọ apata di adágún omi, ati okuta-ìbọn di orisun omi. (Eks 17:6; Num 20:11; Psm 107:35; Deut 8:1.)

## ORIN 115.

**Ọlọrun nikan ni o ni ogo.**

KI i ṣe fun wa, Oluwa, ki i ṣe fun wa, bikoṣe orukọ rẹ ni a fi ogo fun nitori aanu rẹ, ati nitori otitọ rẹ. (Isa 48:11; Esk 36:32; Psm 96:8.)

2. Nitori kinni awọn Keferi yóò ṣe wi pe, "Nibo ni Ọlọrun wọn wa nisinsinyii?" (Psm 42:3; 79:10.)

**Ibi ti o wa ninu ibọriṣa.**

3. Ṣugbọn Ọlọrun wa nbẹ ni ọ̀run: o nṣe ohun-kohun ti o wu u. (Psm 103:19; 135:6; Dan 4:35.)

4. Fadaka ati wura ni ère wọn, iṣẹ́ ọwọ́ eniyan. (Deut 4:28; Psm 135:15–17; Jer 10:3.)

5. Wọn ni ẹnu, ṣugbọn wọn ko sọ̀rọ̀: wọn ni ojú, ṣugbọn wọn ko riran. (Jer 10:5.)

6. Wọn ni etí, ṣugbọn wọn ko gbọran: wọn ni imú, ṣugbọn wọn ko gboorùn.

7. Wọn ni ọwọ́, ṣugbọn wọn ko lo-o; wọn ni ẹsẹ̀, ṣugbọn wọn ko rìn: bẹ̃ wọn ko sọ̀rọ̀ lati ọ̀fun jade.

8. Awọn ti nṣe wọn dabi wọn; bẹ̃ ni olukúlùkù ẹni ti o gbẹkẹle wọn. (Psm 135:18.)

**Ìpè si Israẹli lati gbẹkẹle Oluwa.**

9. Israẹli, iwọ gbẹkẹle Oluwa, Oun ni iranlọwọ wọn ati asà wọn. (Psm 118:2–4; 33:20.)

10. Ara-ile Aarọni, gbẹkẹle Oluwa, Oun ni iranlọwọ wọn ati asà wọn.

11. Ẹyin ti o bẹru Oluwa, gbẹkẹle Oluwa: Oun ni iranlọwọ wọn ati asà wọn. (Psm 135:20.)

**Oluwa yoo bùkún Israẹli.**

12. Oluwa ti nṣe iranti wa; yoo busi i fun wa: yoo busi i fun ara-ile Israẹli; yoo busi i fun ara-ile Aarọni.

13. Yoo busi i fun awọn ti o bẹru Oluwa, ati èwe ati àgbà. (Psm 128:1, 4.)

14. Oluwa yoo mu yin bisi i siwaju ati siwaju, ẹ̀yin ati awọn ọmọ yin. (Deut 1:11.)

15. Ẹyin ni ẹni-ibukun Oluwa, ti o da ọrun ati ayé! (Gen 14:19; 1:1; Psm 96:5.)

16. Ọrun ani ọrun ni ti Oluwa; ṣugbọn ayé ni o fi fun awọn ọmọ eniyan. (Psm 89:11; 8:6.)

17. Okú ko le yin Oluwa, ati gbogbo awọn ti o sọkalẹ lọ sinu idákẹ́. (Psm 6:5; 31:17.)

18. Ṣugbọn awa o maa fi ibukun fun Oluwa, lati igba yií lọ ati titi lae-lae. Ẹ yin Oluwa! (Psm 113:2.)

## ORIN 116.

**Mímọ ríri idande Ọlọrun.**

EMI fẹ Oluwa nitori ti o gbọ ohùn mi ati ẹbẹ mi. (Psm 18:1; 66:19.)

2. Nitori ti o dẹ etí rẹ si mi, nitori naa ni emi o maa ke pè e niwọn ọjọ mi. (Psm 40:1.)

3. Ikaanu ikú yi mi ká, ati irora isà-òkú di mi mú; mo ri iyọnu ati ikaanu. (Psm 18:4–6.)

4. Nigba naa ni mo ke pè orukọ Oluwa; Oluwa, emi bẹ ọ, gba ọkàn mi! (Psm 118:5; 22:20.)

5. Olore-ọfẹ ni Oluwa, ati olododo; nitootọ, alaanu ni Ọlọrun wa. (Psm 103:8; Esra 9:15; Neh 9:8; Psm 145:17; Eks 34:6.)

6. Oluwa pa awọn alaimọkan mọ́: a rẹ mi silẹ tán, o si ràn mi lọwọ. (Psm 19:7; 79:8.)

7. Pada si ibi isinmi rẹ, iwọ ọkàn mi; nitori ti Oluwa ṣe ọ̀pọ̀lọpọ̀ fun ọ. (Jer 6:16; Matt 11:29; Psm 13:6.)

8. Nitori ti iwọ gba ọkan mi lọwọ ikú, oju mi lọwọ omijé, ati ẹsẹ̀ mi lọwọ ìṣubú. (Psm 56:13.)

9. Emi o maa rìn niwaju Oluwa ni ilẹ̀ alààyè. (Psm 27:13.)

10. Emi gbàgbọ́, nitori naa ni emi ṣe sọ: mo ri iponju gidigidi. (2 Kro 4:13.)

11. Mo wi ni iyara mi pe: Èké ni gbogbo eniyan. (Psm 31:22; Rom 3:4.)

**Ipinnu sisan ẹ̀jẹ́.**

12. Kinni emi o san fun Oluwa nitori gbogbo oore rẹ̀ si mi?

13. Emi o mu ago igbala, emi o si maa ke pe orukọ Oluwa. (Psm 16:5; 80:18.)

14. Emi o san ileri ifẹ mi fun Oluwa, nitootọ loju gbogbo awọn eniyan rẹ̀. (Psm 22:25; Jona 2:9.)

15. Iyebíye ni iku awọn àyànfẹ́ rẹ̀ ni ojú Oluwa. (Psm 72:15.)

16. Oluwa nitootọ iranṣẹ rẹ lemi: iranṣẹ rẹ lemi, ati ọmọ iranṣẹbinrin rẹ; iwọ ti tú ìdè mi. (Psm 119:125; 143:86:16.)

17. Emi o rú ẹbọ ọpẹ́ si ọ, emi o maa ke pe orukọ Oluwa. (Psm 50:14; ẹsẹ 13.)

18. Emi o san ileri ifẹ́ mi fun Oluwa, nitootọ loju gbogbo awọn eniyan rẹ̀. (ẹsẹ 14.)

19. Ninu agbala ilé Oluwa, laarin rẹ, iwọ Jerusalẹmu. Ẹ yin Oluwa! (Psm 96:8; 135:2.)

## ORIN 117.

**Yin Oluwa nitori ifẹ rẹ si wa.**

Emaa yin Oluwa, ẹyin orilẹ-ede gbogbo: ẹ yin in, ẹyin eniyan gbogbo. (Rom 15:11.)

2. Nitori ti iṣeun aanu rẹ̀ pọ si wa: ati otitọ Oluwa duro laelae. Ẹ yin Oluwa. (Psm 100:5.)

## ORIN 118.

**Aanu Oluwa.**

EFI ọpẹ́ fun Oluwa; nitori ti o ṣeun, nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae! (Psm 106:1; 136:1.)

2. Jẹ ki Israẹli wi nisinsinyií pe, "Aanu rẹ duro laelae." (Psm 115:9.)

3. Jẹ ki ara-ile Aaroni wi nisinsinyií pe, "Aanu rẹ̀ duro laelae."

4. Jẹ ki awọn ti o bẹru Oluwa wi nisinsinyií pe, "Aanu rẹ duro laelae."

**Idahun Oluwa si àdúrà.**

5. Mo ke pe Oluwa ninu iponju: Oluwa si da mi lóhùn o si da mi nídè. (Psm 120:1; 18:19.)

6. Oluwa nbẹ fun mi, emi ki yoo bẹ̀rù; kinni eniyan le ṣe si mi? (Psm 27:1; Heb 13:6; Psm 56:4,11.)

7. Oluwa nbẹ fun mi pẹlu awọn ti nran mi lọwọ: nitori naa ni emi o ṣe ri

ifẹ mi lori awọn ti o korira mi. (Psm 54:4; 59:10.)

8. Ó dara lati gbẹkẹle Oluwa, ju ati gbẹkẹle eniyan lọ. (Psm 40:4; Jer 17:5.)

9. Ó dara lati gbẹkẹle Oluwa, ju ati gbẹkẹle awọn ọmọ-alade lọ. (Psm 146:3.)

**Idande Oluwa.**

10. Gbogbo awọn orilẹ-ède yí mi ka, ṣugbọn lorukọ Oluwa emi o pa wọn run! (Psm 3:6; 18:40.)

11. Wọn yi mi ka; nitootọ, wọn yi mi ka kiri, ṣugbọn lorukọ Oluwa emi o pa wọn run.

12. Wọn yi mi ká bi oyin; o si pa wọn bi iná ẹgún: ni orukọ Oluwa emi o pa wọn run. (Deut 1:44; Psm 58:9.)

13. Iwọ tì mí gidigidi ki emi le ṣubu; ṣugbọn Oluwa ran mi lọ́wọ́. (Psm 86:17.)

14. Oluwa ni agbara ati orin mi, ọ si di igbala mi. (Eks 15:2; Isa 12:2.)

**Ọwọ́ ọ̀tún nla Oluwa.**

15. Ohun ayọ̀ ati ti igbàlà nbẹ ninu àgọ́ awọn olododo; "ọwọ́ ọ̀tún Oluwa ni a gbéga: ọwọ́ ọ̀tún Oluwa nṣe agbara. (Psm 68:3; 89:13.)

16. Ọwọ́ ọ̀tún Oluwa ni a gbega: ọwọ́ ọ̀tún Oluwa nṣe agbara." (Eks 15:6.)

17. Emi ki yoo kú, bikoṣe yíyè, ki emi si le maa ròhìn iṣẹ́ Oluwa. (Hab 1:12; Psm 73:28.)

18. Oluwa nà mi gidigidi: ṣugbọn kò fi mi fun ikú. (2 Kor 6:9.)

19. Ṣi ilẹkùn ẹnu-ọ̀nà ododo silẹ̀ fun mi; emi o ba ibẹ̀ wọlé, emi o maa yin Oluwa. (Isa 26:2.)

20. Èyí ni ẹnu-ọ̀nà Oluwa, ti awọn olododo yoo gba wọlé. (Psm 24:7; Isa 35:8; Ifh 22:14.)

21. Emi o yin ọ; nitori ti iwọ gbọhun mi, iwọ si di igbàlà mi. (Psm 116:1; ẹsẹ 14.)

**Ọgbọ́n Ọlọrun.**

22. Ọkuta ti awọn ọ̀mọ̀lé kọ silẹ ni o di pataki igun ilé. (Matt 21:42; Mk 12:10; Luk 20:17; A.A. 4:11; Ef 2:20; 1 Pet 2:4,7.)

23. Lati ọdọ Oluwa ni eyiì: o jẹ́ iyanu ni oju wa.

24. Eyí ni ọjọ́ ti Oluwa dá: awa o maa yọ̀, inu wa yoo si maa dùn ninu rẹ.

25. Ṣe igbala nisinsinyìí, emi nbẹ ọ, Oluwa: Oluwa emi bẹ ọ, rán alaafia.

26. Olubukún ni ẹni ti o nbọ wa ni orukọ Oluwa: awa ti fi ibukun fun ọ lati ilé Oluwa wá. (Matt 21:9; Mk 11:9; Luk 13:35; 19:38; Jhn 12:13.)

27. Ọlọrun ni Oluwa, ti o ti fi imọ́lẹ̀ hàn fun wa: ẹ fi okùn di ẹbọ maa mọ́ iwo pẹpẹ naa. (1 A.Ọba 18:39; Est 8:16; 1 Pet 2:9.)

**Orin iyìn fun Olodumare.**

28. Iwọ ni Ọlọrun mi, emi o si maa yin ọ, iwọ ni Ọlọrun mi, emi o maa gbé ọ ga. (Eks 15:2; Isa 25:1.)

29. Ẹ fi ọpẹ́ fun Oluwa; nitori ti o ṣeun, nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae. (ẹsẹ 1.)

ORIN 119.

ALEFI.

**Ibukun wa fun awọn ti o pa ofin Ọlọrun mọ.**

IBUKUN ni fun awọn ẹni ti o pé ni ọ̀nà naa, ti nrin ninu ofin Oluwa. (Psm 101:2,6; 128:1.)

2. Ibukun ni fun awọn ti npa ẹ̀ri rẹ̀ mọ, ti si nwá a kiri tinu-tinu gbogbo. (ẹsẹ 22,10; Deut 6:5.)

3. Wọn ko dẹ́ṣẹ̀ pelu: wọn nrin ni ọ̀nà rẹ̀. (1 Jhn 3:9; 5:18.)

4. Iwọ ti pàṣẹ fun wa lati pa ẹ̀kọ́ rẹ mọ́ gidigidi.

5. Ọna mi iba jẹ la silẹ lati maa pa ilànà rẹ mọ́!

6. Nigba naa ni ojú ki yoo ti mi, nigba ti emi ba njuba àṣẹ rẹ gbogbo. (ẹsẹ 80.)

7. Emi o maa fi àyà diduro-ṣinṣin yin ọ, nigba ti emi ba ti kọ́ idajọ ododo rẹ. (ẹsẹ 62.)

8. Emi o pa ilana rẹ mọ: ma ṣe kọ mi silẹ patapata.

## BETI.

**Pipa òfin Ọlọrun mọ jẹ́ iwa mimọ.**

9. Ọna wo ni ọdọmọkunrin lè fi mu ọ̀nà rẹ̀ mọ́? Nipa ikiyesi gẹgẹ bi ọ̀rọ̀ rẹ. (2 Kro 6:16.)

10. Tinu-tinu mi gbogbo ni emi fi ṣe afẹ́rí rẹ: ma ṣe jẹ ki emi ṣìnà kuro ninu àṣẹ rẹ. (2 Kro 15:15; ẹsẹ 21,118.)

11. Ọ̀rọ̀ rẹ ni mo pamọ́ ni àyà mi, ki emi ma baa ṣẹ̀ si ọ. (Psm 37:31; Luk 2:19,51.)

12. Olubukun ni ìwọ, Oluwa: kọ mi ni ilana rẹ. (Psm 24:4,5; 118: 26,64,108,124,135,171.)

13. Ẹnu mi ni emi fi nsọ gbogbo ìdâjọ́ ẹnu rẹ. (Psm 40:9; ẹsẹ 72.)

14. Emi ti nyọ̀ ni ọ̀nà ẹ̀rí rẹ, bi lori oniruuru ọ̀rọ̀.

15. Emi o maa se àṣàrò ninu ẹ̀kọ́ rẹ emi o si maa juba ọ̀nà rẹ. (ẹsẹ 23,48,78; Psm 1:2.)

16. Emi o maa ṣe inu-didùn ninu ìlànà rẹ; emi ki yoo gbàgbé ọ̀rọ̀ rẹ. (Psm 1:2.)

## GIMELI.

**Awọn ohun ìyanu ti nbẹ ninu òfin.**

17. Fi ọpọlọpọ ba iranṣẹ rẹ lò, ki emi lè wa laaye, ki emi le maa pa ọ̀rọ̀ rẹ mọ́. (Psm 13:6.)

18. La mi loju, ki emi lè maa wo awọn ohun ìyanu wọnni lati inu ofin rẹ. (Gen 47:9; 1 Kro 29:15; Psm 39:12; 2 Kor 5:6; Heb 11:13.)

19. Alejo ni emi ni ayé: maṣe pa àṣẹ rẹ mọ fun mi.

20. Àyà mi nja nitori ifojusona rẹ̀ fun ìdájọ́ rẹ nigbagbogbo. (Psm 42: 1,2.)

21. Iwọ ti ba awọn agberaga wí, ti a ti fi gegun, ti o ti ṣìnà kúrò nipa àṣẹ rẹ. (ẹsẹ 10,118.)

22. Mu ẹ̀gàn ati àbùkù kuro lara mi; nitori ti emi ti pa ẹ̀rí rẹ mọ́. (Psm 39:8.)

23. Awọn ọmọ-alade jókòó pẹlu, wọn nsọrọ mi: ṣugbọn iranṣẹ rẹ nṣe àṣàrò ninu ìlànà rẹ. (ẹsẹ 15.)

24. Ẹrí rẹ pẹlu ni didun-inu mi ati igbimọ mi. (ẹsẹ 16.)

## DALẸFI.

**Adura lati le ni òye ọ̀rọ̀ Ọlọrun.**

25. Ọkàn mi lẹ̀ mọ erupẹ: iwọ sọ mi di ààyè gẹ́gẹ́ bi ọ̀rọ̀ rẹ. (Psm 44:25; ẹsẹ 37.)

26. Emi ti ròhìn ọ̀nà mi, iwọ si gbohun mi: maa kọ mi ni ìlànà rẹ. (ẹsẹ 12.)

27. Mu òye ọ̀nà ẹ̀kọ́ rẹ ye mi: bẹẹ ni emi o maa ṣe àṣàrò iṣẹ́ iyanu rẹ. (Psm 145:5.)

28. Ọkàn mi njoro fun ààrẹ̀: ìwọ mu mi lara le gẹgẹ bi ọ̀rọ̀ rẹ. (Psm 107:26; 20:2; 1 Pet 5:10.)

29. Mu ọ̀nà eke kuro lọdọ mi: ki o si fi oore-ọfẹ ofin rẹ fun mi.

30. Emi ti yan ọ̀nà otitọ: idajọ rẹ ni mo fi lelẹ niwaju mi.

31. Emi ti faramọ ẹ̀rí rẹ: Oluwa máṣe dojuti mi. (Deut 11:22.)

32. Emi o maa sáré ni ọ̀nà aṣẹ rẹ, nitori iwọ fun àyà mi láyè. (1 A.Ọba 4:29; Isa 60:5; 2 Kor 6:11.)

## HE.

**Ileri Ọlọrun nbeere fun iforiti.**

33. Oluwa, kọ mi ni ọ̀nà rẹ; emi o si maa pa a mọ de òpin. (ẹsẹ 5,12.)

34. Fun mi ni òye, emi o si pa òfin rẹ mọ; nitootọ, emi o maa kiyesi tinu-tinu mi gbogbo. (ẹsẹ 73, Owe 2:6; Jms 1:5.)

35. Mu mi rin ni ipa àṣẹ rẹ; nitori ninu rẹ ni didun inu mi. (ẹsẹ 16.)

36. Fa àyà mi si ẹ̀rí rẹ, ki o má si ṣe sí ojú-kòkòrò. (1 A.Ọba 8:58; Luk 12: 15.)

37. Yi ojú mi padà kúrò lati maa wo ohun asán; mu mi yè ni ọ̀nà rẹ. (Isa 33:15; Psm 71:20.)

38. Fi ọ̀rọ̀ rẹ mulẹ̀ si iranṣẹ rẹ, ti nṣe ti awọn to bẹru rẹ. (2 Sam 7:25.)

39. Yí ẹ̀gàn mi pada ti mo bẹ̀rù: nitori ti idajọ rẹ dara.

40. Kiyesi i, ọkan mi ti fà si ẹ̀kọ́ rẹ: sọ mi di ààyè ninu ododo rẹ. (ẹsẹ 20,25.)

### FAU.

**Ìgbàlà nipa òfin Ọlọ̀run.**

41. Jẹ ki aanu rẹ o tọ mi wá pẹlu, Oluwa, àní igbala rẹ gẹ́gẹ́ bi ọ̀rọ̀ rẹ. (ẹsẹ 77,116.)

42. Bẹẹ ni emi o ni ọ̀rọ̀ ti emi o fi da ẹni ti ngan mi lohun; nitori mo gbẹkẹle ọ̀rọ̀ rẹ. (Owe 27:11.)

43. Lootọ máṣe gbà ọ̀rọ̀ otitọ kuro lẹnu mi rara; nitori ti mo ti nṣe ireti ni idajọ rẹ.

44. Bẹẹ ni emi o maa pa ofin rẹ mọ́ patapata titi lae, ati laelae.

45. Bẹẹ ni emi o maa rìn ni alaafia; nitori ti mo wá ẹ̀kọ́ rẹ.

46. Emi o si maa sọ̀rọ̀ ẹ̀rí rẹ niwaju awọn ọba, emi ki yoo si tijú. (Matt 10:18; A.A. 26:1,2.)

47. Emi o si maa ṣe inu-didun ninu àṣẹ rẹ, ti emi ti fẹ́. (ẹsẹ 16.)

48. Ọwọ́ mi pẹlu ni emi o gbe soke si àṣẹ rẹ, ti emi ti fẹ́; emi o si maa ṣe àṣàrò ìlànà rẹ. (ẹsẹ 15.)

### SAIN

**Ofin Ọlọrun ni orisun ìrètí ati ìtùnú.**

49. Ranti ọ̀rọ̀ rẹ si ọmọ-ọdọ rẹ, lara èyí ti iwọ ti mu mi ṣe ìrètí.

50. Eyi ni itunu mi ninu ipọnju mi: nitori ọ̀rọ̀ rẹ ni o sọ mi di ààyè. (Rom 15:4.)

51. Awọn agberaga ti nyọ ṣuti si mi gidigidi: sibẹ emi kò fà sẹhin kuro ninu ofin rẹ. (Jer 20:7; ẹsẹ 157; Job 23:11; Psm 44:18.)

52. Oluwa, emi ranti idajọ atijọ; emi si tu ara mi ninu. (Psm 103:18.)

53. Mo ni ibanujẹ nla nitori awọn eniyan buburu ti o kọ ofin rẹ silẹ. (Esra 9:3; Psm 89:30.)

54. Ìlànà rẹ ni o ti nṣe orin mi ni ilẹ̀ àtìpó mi.

55. Emi ti ranti orukọ rẹ Oluwa, ni òru, emi si ti pa ofin rẹ mọ. (Psm 63:6.)

56. Èyí ni mo ni nitori ti mo pa ẹ̀kọ́ rẹ mọ.

### ṢETI.

**Ọlọrun ni ipin wa.**

57. Oluwa, iwọ ni ìpín mi: emi ti wi pe, emi o pa ọ̀rọ̀ rẹ mọ́. (Psm 16:5; Deut 33:9.)

58. Emi ti nbẹbẹ ojú-rere rẹ tinu-tinu mi gbogbo: ṣaanu fun mi gẹgẹ bi ọ̀rọ̀ rẹ. (1 A.Ọba 13:6; ẹsẹ 41.)

59. Emi ro ọ̀nà mi, mo si yi ẹsẹ̀ mi pada si ẹ̀rí rẹ. (Luk 15:17,18.)

60. Emi yara, emi ko si lọra lati pa ofin rẹ mọ.

61. Okùn awọn eniyan buburu ti yi mi ká: ṣugbọn emi ko gbàgbé ofin rẹ. (Psm 140:5; ẹsẹ 83.)

62. Laarin ọ̀gànjọ́ emi o dide lati dúpẹ́ fun ọ nitori ododo ìdájọ́ rẹ. (A.A. 16:25.)

63. Ẹgbẹ́ gbogbo awọn ti o bẹ̀rù rẹ ni emi, ati ti awọn ti npa ẹ̀kọ́ rẹ mọ́. (Psm. 101:6.)

64. Oluwa, ayé kun fun aanu rẹ: kọ mi ni ilana rẹ. (Psm 33:5; ẹsẹ 12.)

### TETI.

**Ìjìyà ni nmu-ni mọ ofin Ọlọrun.**

65. Iwọ ti nṣe rere fun iranṣẹ rẹ Oluwa, gẹgẹ bi ọ̀rọ̀ rẹ.

66. Kọ mi ni ìwà ati ìmọ̀ rere; nitori ti mo gba àṣẹ rẹ gbọ́.

67. Ki a to pọn mi loju emi ti ṣìnà: ṣugbọn nisinsinyìí emi ti pa ọ̀rọ̀ rẹ mọ́. (Ẹsẹ 71; Jer 31:18,19; Heb 12:11.)

68. Iwọ ṣeun iwọ si nṣe rere; kọ mi ni ìlànà rẹ. (Psm 106:1; Deut 8:16; ẹsẹ 12.)

69. Awọn agberaga ti hùmọ̀ èké si mi: ṣugbọn emi o pa ẹ̀kọ́ rẹ mọ tinú-tinú mi gbogbo. (Job 13:4; ẹsẹ 56.)

70. Àyà wọn sébọ́ bi ọ̀rá; ṣugbọn emi o ṣe inu-didun ninu òfin rẹ. (Psm 17:10; Isa 6:10; ẹsẹ 16.)

71. O dara fun mi ti a pọn mi loju; ki emi le kọ́ ìlànà rẹ.

72. Ofin ẹnu rẹ dara fun mi ju ẹgbẹẹgbẹrun wúrà ati fadaka lọ. (ẹsẹ 127; Psm 19:10; Owe 8:10,11,19.)

### JOD.

**Awọn ẹlẹgbẹ mi ni awọn ti o mọ òfin Oluwa.**

73. Ọwọ́ rẹ ni o ti da mi, ti o si ṣe àwòrán mi: fun mi ni òye, ki emi lè kọ́ àṣẹ rẹ. (Job 10:8; Psm 138:8; ẹsẹ 34.)

74. Inu awọn ti o bẹ̀rù rẹ yoo dun, nigba ti wọn ba ri mi; nitori ti mo ni ìrètí ni ọ̀rọ̀ rẹ. (Psm 34:2; ẹsẹ 43.)

75. Oluwa, emi mọ̀ pe, ododo ni idajọ rẹ, ati pé ninu òótọ́ ni iwọ pọ́n mi loju. (Heb 12:10.)

76. Emi bẹ ọ, jẹ ki ìṣeun-aanu rẹ maa ṣe ìtùnu mi gẹ́gẹ́ bi ọ̀rọ̀ rẹ si iranṣẹ rẹ.

77. Jẹ ki irọnu aanu rẹ o tọ̀ mi wá, ki emi le yè: nitori ofin rẹ ni didùn-inu mi. (ẹsẹ 41,47.)

78. Jẹ ki ojú o ti agberaga; nitori ti wọn ṣe àrekérkè si mi láinídii. Ṣugbọn emi o maa ṣe àṣàrò ninu ẹ̀kọ́ rẹ.

79. Jẹ kí awọn ti o bẹ̀rù rẹ o yipada si mi, ati awọn ti o ti mọ ẹ̀rí rẹ.

80. Jẹ ki àyà mi pé ni ìlànà rẹ; ki oju má ṣe ti mi. (ẹsẹ 1,46.)

### KAFI.

**Ṣiṣe àfẹ́rí alaafia.**

81. Ọkàn mi ndákú fun igbala rẹ; ṣugbọn emi ni ìrètí ni ọ̀rọ̀ rẹ. (Psm 84:2.)

82. Ojú mi nwọna titi nitori ọ̀rọ̀ rẹ, wi pe, "Nigbawo ni iwọ yoo tù mi nínú? (Psm 69:3.)

83. Nitori ti emi dabi igo-awọ ninu eefin; ṣugbọn emi kò gbagbe ilana rẹ. (Job 30:30.)

84. Ijọ́ melo ni ọjọ iranṣẹ rẹ? Nigbawo ni iwọ o ṣe idajọ lara awọn ti nṣe inunibini si mi? (Psm 39:4; Ifh 6:10.)

85. Awọn agberaga ti wà ihò silẹ̀ dè mi, ti ki i ṣe gẹgẹ bi ofin rẹ. (Psm 35:7.)

86. Otitọ ni àṣẹ rẹ gbogbo: wọn fi arekereke ṣe inunibini si mi: iwọ ràn mi lọ́wọ́. (ẹsẹ 78; Psm 35:19; 109: 26.)

87. Wọn fẹ́rẹ̀ run mi lori ilẹ̀; ṣugbọn emi kò kọ̀ ẹ̀kọ́ rẹ silẹ. (Isa 58:2.)

88. Sọ mi di aaye gẹgẹ bi iṣeun-aanu rẹ: bẹẹ ni emi o si pa ẹ̀rí ẹnu rẹ mó.

### LAMED.

**Ọ̀rọ̀ Oluwa duro ṣinṣin.**

89. Titi lae, Oluwa, ni ọ̀rọ̀ rẹ duro ṣinṣin ni ọ̀run. (Matt 24:34; 35.)

90. Lati ìran-diran ni otitọ rẹ; iwọ ti fi ìdí ayé múlẹ̀, o si duro. (Psm 36:5; 148:6; Onws 1:4.)

91. Wọn duro di oni nipa idajọ rẹ: nitori pé iranṣẹ rẹ ni gbogbo wọn. (Jer 33:25.)

92. Bikoṣe pé bi ofin rẹ bá ṣe inu didun mi, emi iba ti ṣègbé ninu ipọnju mi. (ẹsẹ 16,50.)

93. Lae emi ki yoo gbagbe ẹ̀kọ́ rẹ; nitori pé awọn ni ìwọ fi sọ mi di ààyè. (ẹsẹ 16,25.)

94. Tirẹ ni emi, gbà mi; nitori ti emi wá ẹ̀kọ́ rẹ. (Psm 146:45.)

95. Awọn eniyan buburu ti duro de mi lati pa mi run: ṣugbọn emi o kiyesi ẹ̀rí rẹ.

96. Emi ti ri òpin ohun pípé gbogbo: ṣugbọn àṣẹ rẹ gboòrò gidigidi.

### MEM.

**Ifẹ ni ofin Oluwa.**

97. Emi ti fẹ ofin rẹ tó! àṣàrò mi ni lọjọ gbogbo. (Psm 1:2.)

98. Nipa àṣẹ rẹ iwọ mu mi gbọn ju awọn ọta mi lọ: nitori tí o wà pẹlu mi laelae. (ẹsẹ 130; Deut 4:6.)

99. Emi ni ìyè ninu ju gbogbo awọn olukọ mi lọ, nitori pé ẹ̀rí rẹ ni àṣàrò mi. (ẹsẹ 15.)

100. Òye yé mi ju awọn àgbà lọ, nitori ti mo pa ẹ̀kọ́ rẹ mọ́. (Job 32:7–9.)

101. Mo ti fa ẹsẹ̀ mi sẹhin kuro nipa ọ̀nà ibi gbogbo, ki emi le pa ọ̀rọ̀ rẹ mọ. (Owe 1:15.)

102. Emi ko yà kuro ni idajọ rẹ: nitori pé iwọ ni o kọ mi.

103. Ọ̀rọ̀ rẹ ti dun mọ́ mi lẹnu tó! o ju oyin lọ lẹnu mi! (Psm 19:10.)

104. Nipa ẹ̀kọ́ rẹ emi ni iyè ninu: nitori naa mo korira ọ̀nà èké gbogbo. (ẹsẹ 128,130.)

NUN.

**Òfin Oluwa ni fitila si ẹsẹ̀ mi.**

105. Ọ̀rọ̀ rẹ ni fitila fun ẹsẹ̀ mi, ati imọlẹ si ipa ọ̀nà mi. (Owe 6:23.)

106. Emi ti búra, emi o si mu un ṣẹ, pé, emi o pa idajọ ododo rẹ mọ́. (Neh 10:29.)

107. A pọ́n mi loju gidigidi: Oluwa sọ mi di ààyè, gẹgẹ bi ọ̀rọ̀ rẹ. (ẹsẹ 25.)

108. Emi bẹ̀ ọ́, Oluwa, gba ọrẹ atinuwa ẹnu mi, ki o si kọ́ mi ni idajọ rẹ. (Hos 14:2; Heb 13:15; ẹsẹ 12.)

109. Ẹmí mi wa lọwọ mi nigbagbogbo: emi kò sì gbagbe ofin rẹ. (Job 13:14; ẹsẹ 16.)

110. Awọn eniyan buburu ti dẹkùn silẹ fun mi: ṣugbọn emi ko ṣìnà kuro nipa ẹ̀kọ́ rẹ. (Psm 140:5; 141:9; ẹsẹ 10.)

111. Ẹri rẹ ni ogún mi laelae: nitori awọn ni ayọ̀ inu mi. (Deut 33:4; ẹsẹ 14,162.)

112. Emi ti fa àyà mi si ati pa ìlànà rẹ mọ́ nigbagbogbo, ani de opin. (ẹsẹ 33.)

SAMEKI.

**Ilé isadi ni ǒfin Oluwa.**

113. Emi korira oniyemeji: ṣugbọn ofin rẹ ni mo fẹ́; (Jak 1:8; ẹsẹ 47.)

114. Iwọ ni ibi ìpamọ́ mi ati asà mi: emi nṣe ireti ninu ọ̀rọ̀ rẹ. (Psm 32:7; 91:1; ẹsẹ 74.)

115. Kuro lọdọ mi, ẹyin oluṣe-buburu: emi o si pa ofin Ọlọrun mi mọ. (Psm 6:8; 139:19; Matt 7:23.)

116. Gbe mi soke gẹgẹ bi ọ̀rọ̀ rẹ, ki emi le yè: ki o ma si jẹ ki ojú ìrètí mi o ti mi. (Psm 54:4; 25:2; Rom 5:5; 9:33.)

117. Gbé mi soke, emi o si wà ni ailewu: emi o si júbà ilana rẹ nigbagbogbo.

118. Iwọ ti tẹ̀ gbogbo awọn ti o ṣìnà kuro ninu ìlànà rẹ mọlẹ: nitori pé ẹ̀tàn ni ironu wọn. (ẹsẹ 21.)

119. Iwọ ṣá gbogbo awọn eniyan buburu ayé tì bi ìdàrọ́: nitori naa emi fẹ ẹ̀rí rẹ. (Esk 22:18.)

120. Ara mi wárìrì nitori ìbẹ̀rù rẹ; emi si bẹru ìdájọ́ rẹ. (Hab 3:16.)

AIN.

**Olorin naa npa ofin Oluwa mọ.**

121. Emi ti ṣe idajọ ododo: iwọ má ṣe fi mi lé aninilara mi lọwọ.

122. Ṣe onígbọ̀wọ́ fun iranṣẹ rẹ rere: máṣe jẹ ki awọn agberaga o ni mi lara. (Job 17:3.)

123. Ojú kún mi nitori ìgbàlà rẹ, ati nitori ọ̀rọ̀ ododo rẹ. (ẹsẹ 81,82.)

124. Ṣe si iranṣẹ rẹ gẹgẹ bi aanu rẹ, ki o si kọ́ mi ni ìlànà rẹ. (ẹsẹ 12.)

125. Iranṣẹ rẹ ni emi: fun mi ni òye, emi o si mọ̀ ẹ̀rí rẹ. (Psm 116:16.)

126. Oluwa, ó tó àkókò fun ọ lati ṣiṣẹ: nitori ti wọn ti sọ ofin rẹ di òfo.

127. Nitori naa emi fẹ àṣẹ rẹ ju wúrà, àní, ju wura didara lọ. (Psm 19:10.)

128. Nitori naa emi ka gbogbo ẹ̀kọ́ rẹ si otitọ patapata: emi si korira gbogbo ọ̀nà èké. (ẹsẹ 104.)

PE.

**Adura fun Oore-Ọfẹ lati le pa ofin Oluwa mọ.**

129. Iyanu ni ẹ̀rí rẹ: nitori naa ni ọkàn mi ṣe pa wọn mọ. (ẹsẹ 18,22.)

130. Ìfihàn ọ̀rọ̀ rẹ funni ni imọlẹ; o si fi òye fun awọn òpè. (Owe 6:23; Psm 19:7.)

131. Emi ya ẹnu mi, emi mí hẹlẹ́: nitori ti ọkàn mi fà si àṣẹ rẹ. (Psm 42:1; ẹsẹ 20.)

132. Iwọ bojuwò mi; ki o si ṣaanu fun mi, gẹ́gẹ́ bi iṣẹ́ rẹ si awọn ti o fẹ orukọ rẹ. (Psm 25:16.)

133. Fi iṣisẹ mi múlẹ̀ ninu ọ̀rọ̀ rẹ: ki o ma si jẹ ki ẹ̀ṣẹ̀kẹ́ṣẹ̀ o jọba lori mi. (Psm 17:15; 19:13.)

134. Gbà mi lọwọ inilara eniyan; bẹẹ ni emi o si maa pa ẹkọ rẹ mọ. (Psm 142:6.)

135. Ṣe oju rẹ ki o mọlẹ si iranṣẹ rẹ lara; ki o si kọ mi ni ilana rẹ. (Psm 4:6; ẹsẹ 12.)

136. Odò omi ṣan silẹ loju mi nitori wọn kò pa ofin rẹ mọ́. (Jẹr 9:1; Esk 9:4.)

SADDI.

**Olododo ni Ọlọrun, idajọ Rẹ si jẹ ododo.**

137. Olododo ni ìwọ, Oluwa, ati diduro-ṣinṣin ni idajọ rẹ. (Esra 9:15; Neh 9:13; Jer 12:1.)

138. Iwọ paṣẹ ẹ̀rí rẹ ni ododo ati otitọ gidigidi. (Psm 19:7–9.)

139. Ìtara mi ti pa mi run nitori ti awọn ọ̀tá mi ti gbagbe ọ̀rọ̀ rẹ (Psm 69:9.)

140. Funfun gbò ni ọ̀rọ̀ rẹ: nitori naa ni iranṣẹ rẹ ṣe fẹ́ e. (Psm. 12:6.)

141. Emi kéré mo si jẹ ẹni ẹ̀gàn: Ṣugbọn emi ko gbagbe ẹ̀kọ́ rẹ.

142. Ododo rẹ ododo laelae ni, otitọ sì ni ofin rẹ. (Psm 19:9; ẹsẹ 151,160.)

143. Ìyọnu ati àròkàn dì mi mú: ṣugbọn àṣẹ rẹ ni inu-didùn mi. (ẹsẹ 24,77.)

144. Ododo ẹ̀rí rẹ aye-raye ni: fun mi ni òye, emi o si yè. (Psm 19:9; ẹsẹ 34,73.)

KỌFÌ.

**Ikigbe fún ìgbàlà.**

145. Tinu-tinu mi gbogbo ni mo fi kigbe; Oluwa da mi lóhùn; emi o pa ilànà rẹ mọ́. (ẹsẹ 10,22,55.)

146. Emi kigbe si ọ; gbà mí là, emi o si maa pa ẹ̀rí rẹ mọ́.

147. Emi ṣaaju jí kutukutu owurọ, emi ké: emi nṣe ìrètí ninu ọ̀rọ̀ rẹ̀.

148. Ojú mi ṣaaju ìṣọ́-òru, ki emi o le maa ṣe àṣàrò ninu ọ̀rọ̀ rẹ. (Psm 5:3.)

149. Gbóhùn mi gẹgẹ bi aanu rẹ: Oluwa, sọ mi di ààyè gẹgẹ bi idajọ rẹ. (ẹsẹ 40,154.)

150. Awọn ti nlepa ìwà-ìkà sunmọ tòsí: wọn Jinna si ofin rẹ.

151. Oluwa, iwọ wa ni tòsí: otitọ si ni gbogbo aṣẹ rẹ. (Psm 145:18; ẹsẹ 142.)

152. Lati inu ẹ̀rí rẹ, emi ti mọ nigba atijọ pe, iwọ ti fi ìdí wọn múlẹ̀ laelae. (Luk 21:33.)

RE ṢI.

**Pipa ofin Ọlọrun mọ́ ninu iponju.**

153. Wo iponju mi, ki o si gbà mi: nitori ti emi ko gbàgbé ofin rẹ. (ẹsẹ 50; Owe 3:1.)

154. Gbà ẹjọ́ mi rò, ki o rà mi pada: sọ mi di ààyè nipa ọ̀rọ̀ rẹ. (1 Sam 24:15; ẹsẹ 134.)

155. Ìgbàlà jinna si awọn eniyan buburu: nitori ti wọn kò wá ìlànà rẹ. (Job 5:4.)

156. Ọ̀pọ ni irọnu aanu rẹ, Oluwa: sọ mi di ààyè gẹgẹ bi idajọ rẹ. (2 Sam 24:14.)

157. Ọ̀pọ̀ ni awọn oninunibini mi ati awọn ọta mi; ṣugbọn emi kò fà sẹhin kuro ninu ẹ̀rí rẹ. (Psm 7:1; ẹsẹ 51.)

158. Emi wò awọn ẹlẹ̀tàn, inu mi si bàjẹ́; nitori ti wọn kò pa ọ̀rọ̀ rẹ mọ́. (Psm 139:21.)

159. Wò bi emi ti fẹ ẹ̀kọ́ rẹ: Oluwa sọ mi di ààyè gẹ́gẹ́ bi aanu rẹ. (ẹsẹ 47:88.)

160. Otitọ ni ipilẹṣẹ ọ̀rọ̀ rẹ; ati idajọ ododo rẹ kọ̀ọkan duro laelae. (Psm 139:17; ẹsẹ 142.)

**Adura fun ìgbàlà kuro lọwọ inunibini.**

161. Awọn ọmọ-alade ṣe inunibini si mi ni àìnídìí: ṣugbọn ọkàn mi wárìrì nitori ọ̀rọ̀ rẹ. (1 Sam 24:11.)

162. Emi yọ̀ si ọ̀rọ̀ rẹ, bi ẹni ti o ri ìkógun pupọ. (1 Sam 30:16.)

163. Emi korira, mo si takété si èké ṣíṣe: ṣugbọn ofin rẹ ni mo fẹ́.

164. Nigba meje lóòjọ́ ni emi nyin ọ nitori ododo idajọ rẹ. (ẹsẹ 7,160.)

165. Alaafia pupọ ni awọn ti o fẹ ofin rẹ ni: ko si si ohun ìkọsẹ fun wọn. (Owe 3:2; Isa 26:3; 32:17.)

166. Oluwa, emi ti nreti ìgbàlà rẹ, emi si ṣe àṣẹ rẹ. (ẹsẹ 174; Gen 49:18.)

167. Ọkàn mi ti pa ẹ̀rí rẹ mọ́; emi si fẹ wọn gidigidi.

168. Emi ti npa ẹ̀kọ́ ati ẹ̀rí rẹ mọ, nitori ti gbogbo ọ̀nà mi nbẹ niwaju rẹ. (Owe 5:21.)

**Ìpè sí Oluwa.**

169. Oluwa, jẹ ki ẹkún mi sunmọ, iwaju rẹ: fun mi ni òye gẹ́gẹ́ bi ọ̀rọ̀ rẹ. (Psm 18:6; ẹsẹ 27,65.)

170. Jẹ ki ẹ̀bẹ̀ mi ó wá siwaju rẹ: gba mi gẹ́gẹ́ bi ọ̀rọ̀ rẹ. (Psm 28:2; 31:2.)

171. Ètè mi yoo sọ ìyìn jade, nigba ti iwọ ba ti kọ́ mi ni ìlànà rẹ. (Psm. 51:15; 94:12.)

172. Ahọ́n mi yoo sọ ni ti ọ̀rọ̀ rẹ: nitori pé ododo ni gbogbo àṣẹ rẹ.

173. Jẹ ki ọwọ́ rẹ ran mi lọwọ; nitori ti mo ti yan ẹ̀kọ́ rẹ. (Psm 37:24.)

174. Oluwa, ọkàn mi ti fa si ìgbàlà rẹ; ofin rẹ si ni dídùn-inú mi. (ẹsẹ 166:24.)

175. Jẹ ki ọkàn mi wa láàyè, yoo si maa yin ọ; si jẹ ki idajọ rẹ maa ran mi lọwọ. (Isa 55:3.)

176. Emi ti ṣìnà kiri bi agutan ti o nù; wá iranṣẹ rẹ nitori ti emi kò gbagbe àṣẹ rẹ. (Isa 53:6; ẹsẹ 16.)

ORIN 120.

**Ìgbàlà kuro lọwọ ahọ́n ẹ̀tàn.**

NINU ipọnju mi emi ke pe Oluwa, o si da mi lóhùn. (Psm 102:2; Jona 2:2.)

2. "Oluwa, gbà ọkàn mi, lọwọ ètè èké, ati lọ́wọ́ ahọ́n ẹ̀tàn." (Owe 12: 22; O.D. 52:4.)

3. Kinni ki a fi fun ọ? Tabi kinni ki a ṣe si ọ, ahọ́n ẹ̀tàn?

4. Ọfà mímú alagbara, pẹ̀lú ẹ̀yin-iná igi juniperi! (Psm 45:5; 140:10.)

**Igbala kuro lọwọ awọn ti o korira alaafia.**

5. Ègbé ni fun mi, ti mo ṣe àtìpó ni Meṣeki, ti mo jokòó ninu àgọ́ Kedari! (Gen 10:2; Esk 27:13; Gen 25:13; Jer 49:28.)

6. O ti pẹ ti ọkàn mi ti ba ẹni ti o korira alaafia gbé.

7. Alaafi ni mo fẹ́: ṣugbọn nigba ti mo ba sọ̀rọ̀, ìjà ni ti wọn. (Psm 55:21.)

ORIN 121.

**Oluwa ni Olupamọ mi.**

EMI o gbe ojú mi soke si awọn okè Nibo ni iranlọ́wọ́ mi yoo ti wá?

2. Iranlọwọ mi yoo ti ọwọ́ Oluwa wá, ti o da ọ̀run ati ayé. (Psm 124:8.)

3. Oun ki yoo jẹ ki ẹsẹ̀ rẹ o yẹ̀; ẹni ti npa ọ mọ́ ki yoo toogbe. (Psm 66:9; 127:1.)

4. Kiyesii, ẹni ti npa Israẹli mọ́, ki i toogbe, bẹ́ẹ̀ ni ki í sun.

5. Oluwa ni olupamọ rẹ; Ọluwa ni ojiji rẹ ni ọwọ́ ọ̀tún rẹ. (Isa 25:4; Psm 16:8.)

6. Oorun ki yoo pa ọ nigba ọ̀sán, tabi òṣùpá nigba òru. (Psm 91:5; Isa 49:10; Ifh 7:16.)

7. Oluwa yoo pa ọ mọ́ kuro ninu ibi gbogbo; yoo pa ọkàn rẹ mọ́. (Psm 91:10–12.)

8. Oluwa yoo pa àlọ ati àbọ̀ rẹ mọ́ lati igba yìí lọ, ati titi laelae. (Deut 28:6.)

ORIN 122.

**Ẹ jẹ ki a lọ si ile Oluwa.**

INU mi dun nigba ti wọn wi fun mi pe, "Ẹ jẹ ki a lọ si ile Oluwa." (Isa 2:3; Sek 8:21.)

2. Ẹsẹ̀ wa yoo duro ni ẹnu-bode rẹ, iwọ Jerusalẹmu.

3. Jerusalẹmu, iwọ ti a kọ́ bi ilu ti o fi ara mọra pọ̀ ṣọkan. (Psm 48:13.)

4. Nibi ti awọn ẹ̀yà maa ngoke lọ, awọn ẹ̀yà Oluwa, ẹ̀rí fun Israẹli, lati maa dupẹ fun orukọ Oluwa. (Deut 16:16; Eks 16:34.)

5. Nitori ibẹ̀ ni a gbé ìtẹ́ idajọ kalẹ̀, awọn ìtẹ́ ile Dafidi. (Deut 17:8; 2 Kro 19:8.)

**Adura fun alaafia ati ṣiṣe rere Jerusalẹmu.**

6. Gbadura fun alaafia Jerusalẹmu: "awọn ti o fẹ ọ yoo ṣe rere. (Psm 51:18.)

7. Ki alaafia o wa ninu odi rẹ, ati ire ninu aafin rẹ."

8. Nitori awọn arakunrin ati awọn ẹgbẹ mi, emi o wi nisinsinyii pé, "Ki alaafia o wa ninu rẹ!"

9. Nitori ti ile Oluwa Ọlọrun wa, emi o maa wa ire rẹ. (Neh 2:10.)

ORIN 123.

**Wíwojú Ọlọrun.**

IWỌ ni mo gbe ojú mi soke si, iwọ ti ngbe inu ọrun. (Psm 121:1; 141:8; 2:4; 11:4.)

2. Kiyesi i, bi oju awọn iranṣẹ-kunrin ti maa nwo ọwọ awọn ọgá wọn, ati bi oju iranṣẹ-binrin ti maa nwo ọwọ oluwa rẹ; bẹẹ ni oju wa nwo Oluwa Ọlọrun wa, titi yoo fi ṣaanu fun wa. (Owe 27:18; Psm 25:15.)

**Adura fun aanu.**

3. Oluwa, ṣaanu fun wa, ṣaanu fun wa: nitori ti a kún fun ẹgàn pupọ-pupọ. (Psm 4:1; 51:1.)

4. Ọkàn wa kún pupọ-pupọ fun ẹgàn awọn onirera, ati fun ẹgàn awọn agberaga. (Psm 79:4.)

ORIN 124.

**Ọlọrun nikan ni Olugbala.**

IBA máṣe pé Oluwa ti o ti wà ni ti wa, ni ki Israẹli maa wi nisinsinyii; (Psm 94:17; 129:1.)

2. Iba máṣe pé Oluwa ti o ti wa ni ti wa, nigba ti awọn eniyan dide si wa,

3. Nigba naa ni wọn iba gbé wa mi laaye, nigba ti ibinu wọn rú si wa: (Psm 56:1; 57:3; Owe 1:12.)

4. Nigba naa ni awọn omi wọnyii iba bo wa mọlẹ, iṣan omi iba ti borí ọkàn wa:

5. Nigba naa ni agberaga omi iba borí ọkàn wa. (Psm 69:2.)

**Olubukun ni Olugbala.**

6. Olubukun ni Oluwa, ti kò fi wa fun wọn bi ohun ọdẹ fun ehin wọn. (Psm 27:2.)

7. Ọkàn wa yọ bi ẹyẹ jade kuro ninu okùn apẹyẹ: okùn já, awa si yọ. (Owe 6:5; Psm 91:3.)

8. Iranlọwọ wa nbẹ lorukọ Oluwa, ti o da ọrun ati aye. (Psm 121:2; Gen 1:1.)

ORIN 125.

**Oluwa ni ààbò wa.**

AWỌN ti o gbẹkẹle Oluwa yoo dabi òkè Sioni, ti a kò lè ṣí ni idí, bikoṣe pé o duro laelae. (Psm 46:5.)

2. Bi òkè nla ti yi Jerusalẹmu ká, bẹẹ ni Oluwa yi awọn eniyan rẹ ká lati isinsinyii lọ ati titi laelae. (Sek 2:5; Psm 121:8.)

3. Nitori ti ọpá awọn eniyan buburu ki yoo ba le ipín awọn olododo, ki awọn olododo má baa fi ọwọ wọn le ẹṣẹ. (Owe 22:8; Isa 14:5; Psm 55:20.)

4. Oluwa ṣe rere fun awọn ẹni-rere, ati fun awọn ti àyà wọn duro ṣinṣin. (Psm 119:68; 7:10; 94:15.)

5. Bi o ṣe ti irú awọn ti wọn ya si ipa ọnà wíwọ wọn: Oluwa yoo jẹ ki wọn lọ pẹlu awọn oniṣẹ ẹṣẹ: ṣugbọn alaafia yoo wa lori Israẹli. (Owe 2:15; Psm 128:6.)

ORIN 126.

**Orin ọpẹ fun idande Oluwa.**

NIGBA ti Oluwa mu ikólọ Sioni padà, awa dabi ẹni ti nlá àlá. (Psm 85:1; A.A. 12:9.)

2. Ni igbà naa lẹnu wa kún fun ẹrín, ati ahọn wa kọ orin: nigba naa ni wọn wi ninu awọn Keferi pé, "Oluwa ṣe ohun nla fun wọn." (Job 8:21; Psm 51:14; 71:19.)

3. Oluwa ṣe ohun nla fun wa: nitori naa awa nyọ. (Isa 25:9.)

4. Oluwa mu ikolọ wa padà, bi iṣàn-omi ni gúsù. (Isa 35:6; 43:19.)

5. Awọn ti nfi omijé fun irúgbìn yoo fi ayọ̀ ka. (Jer 31:16; Isa 35:10.)

6. Ẹni ti nfi ẹkún rin lọ, ti ó si gbé irúgbìn lọwọ, lootọ, yoo fi ayọ̀ pada wá, yoo si rù ìtí rẹ.

ORIN 127.

**Asán ni iṣẹ́ laisi Ọlọrun.**

BÍKÒṢE pe Oluwa bá kọ́ ile naa, awọn ti nkọ́ ọ nṣiṣẹ lásán: bikose pe Oluwa ba pa ilu mọ́, oluṣọ jí lásán. (Psm 78:69; 121:4.)

2. Asán ni fun ẹyin ti ẹ dide ni kutukutu lati pẹ ṣíwọ́, lati jẹ ounjẹ ikaanu: bẹẹ ni o nfi ire fun olufẹ rẹ̀ loju oorun. (Gen 3:17; Job 11:18,19.)

3. Kiyesi i, awọn ọmọ ni ìní Oluwa: ọmọ inú si ni èrè rẹ̀. (Gen 33:5; Jos 24:3,4; Deut 28:4.)

4. Bi ọfà ti ri lọ́wọ́ alagbara, bẹẹ ni awọn ọmọ èwe.

5. Ibukun ni fun ọkunrin naa ti àpó rẹ̀ kun fún wọn: ojú ki yoo tì wọ́n, ṣugbọn wọn o ṣẹgun awọn ọ̀tá ni ẹnu ibodè. (Job 5:4; Owe 27:11.)

ORIN 128.

**Ibukun fun Olukuluku eniyan.**

IBUKUN ni fun gbogbo ẹni ti o bẹ̀rù Oluwa; ti ó si nrin ni ọ̀nà rẹ̀. ( Psm 112:1; 119:3.)

2. Nitori ti iwọ o jẹ iṣẹ́ ọwọ́ rẹ: ibukun ni fun ọ: yoo si dara fun ọ. (Isa 3:10; Esk 23:29; Onws 8:12.)

**Ibukun fun ilé.**

3. Obinrin rẹ yoo dabi àjàrà rere eléso pupọ laarin ile rẹ: awọn ọmọ rẹ yoo dabi igi olifi yí tabili rẹ ká. (Esk 19:10; Psm 52:8; 144:12.)

4. Kiyesi i, pe bẹẹ ni a o busi fun ọkunrin naa, ti o bẹru Oluwa.

**Ibukun fun orilẹ-èdè.**

5. Ki Oluwa o busi i fun ọ lati Sioni wá, ki o si maa ri ire Jerusalẹmu lọjọ ayé rẹ gbogbo. (Psm 134:3: 20:2; 122:9.)

6. Bẹẹ ni ki iwọ si maa ri ọmọ ọmọ rẹ: ki alaafia wa fun Israẹli! (Gen 50:23; Job 42:16; Psm 125:5.)

ORIN 129.

**Adura fun ìtìjú awọn ọta Israẹli.**

IGBA pupọ ni wọn ti npọn mi loju lati igba-èwe mi wa," jẹ ki Israẹli o wi nisinsinyìí. (Psm 88:15; 124:1; Hos 2:15.)

2. "Igba pupọ ni wọn ti npọn mi loju lati ìgbà-èwe mi wá: sibẹ wọn kòì tíì borí mi. (Matt 16:18.)

3. Awọn awalẹ̀ walẹ̀ si ẹ̀hìn mi: wọn si la aporó wọn gigun.

4. Olododo ni Oluwa: o ti ge okùn awọn eniyan buburu kúrò." (Psm 119:137.)

5. Ki gbogbo awọn ti o korira Sioni o daamu, ki wọn si yi ẹhin pada. (Mika 4:11; Psm 71:13.)

6. Ki wọn o dabi koriko ori-ilẹ ti o gbẹ dànù, ki o to dàgbà sókè: (Psm 37:2.)

7. Eyí ti olukore ko fi kun ọwọ́ rẹ̀; bẹẹ ni ẹni ti ndi ìtí, kò kun apá rẹ̀.

8. Bẹẹ ni awọn ti nkọja lọ ko wi pe, "Ibukun Oluwa ki o pẹlu yín! awa sure fun yin ni orukọ Oluwa!" (Rut 2:4; Psm 118:26.)

ORIN 130.

**Igbe fún iranlọwọ.**

LATI inu ìbú wa ni emi ke pe ọ, Oluwa. (Psm 42:7; 69:2.)

2. Oluwa, gbohun mi, jẹ ki etí rẹ ó tẹ́ silẹ si ohun ẹ̀bẹ̀ mi. (Psm 64:1; 2 Kro 6:40; Psm 28:2.)

3. Oluwa, bi o ba se pe iwo nsàmì ẹ̀ṣẹ̀, Oluwa, tani ìbá dúró? (Psm 76: 7.)

4. Nitori idariji wa lọ́dọ̀ rẹ, ki a le maa bẹ̀rù rẹ. (Eks 34:7; Isa 55:7; 1 A.Ọba 8:40; Jer 33:8.)

**Diduro de Oluwa pẹlu suuru.**

5. Emi duro de Oluwa, ọkàn mi duro, ati ninu ọ̀rọ̀ rẹ̀ ni emi nṣe ìrẹ̀tí. (Psm 33:20; Isa 8:17; Psm 119:81.)

6. Ọkàn mi duro de Oluwa, ju awọn ti nṣọ́nà owurọ lọ, àní ju awọn ti nṣọ́nà owurọ lọ. (Psm 63:6; 119:147.)

**Ìpè lati ni ireti ninu Oluwa.**

7. Israẹli, iwọ ni ireti ni ti Oluwa; nitori pé lọdọ Oluwa ni aanu wà, ati lọdọ rẹ̀ ni ọpọlọpọ idande wa. (Psm 131:3; Isa 55:7.)

8. Oun o si da Israẹli nídè kúrò ninu ẹ̀ṣẹ̀ rẹ gbogbo. (Luk 1:68.)

## ORIN 131.

**Orin eniyan pẹ̀lẹ́.**

OLUWA, àyà mi kò gbega, bẹẹ ni ojú mi ko gbe sókè: bẹẹ ni emi ko fi ọwọ́ mi le ọ̀ràn nla, tabi le ohun ti o ga jù mi lọ. (Psm 101:5; Isa 5:15; Rom 12:16.)

2. Nitootọ emi mu ọkàn mi sinmi, mo si mu un dakẹjẹ, bi ọmọ ti a ti ọwọ́ ìyá rẹ̀ gba lẹnu ọmú ọkàn mi ri gẹ́gẹ́ bi ọmọ ti a ja lẹnu ọmú. (Psm 62:1; Matt 18:3; 1 Kro 14:20.)

3. Israẹli, iwọ ni ireti ni ti Oluwa lati isinsinyìí lọ ati laelae. (Psm 130:7.)

## ORIN 132.

**Ibura Dafidi.**

OLUWA, ranti Dafidi ninu gbogbo iponju rẹ̀.

2. Eni ti o ti bura fun Oluwa, ti o si ṣe ileri ìfẹ́ fun Alagbara Jakọbu pe, (Gen 49:24.)

3. "Nitootọ, emi ki yoo wọ inu àgọ́ ile mi lọ, bẹẹ ni emi ki yoo gun orí akete mi.

4. Emi ki yoo fi oorun fun ojú mi, tabi oogbe fun ipenpeju mi. (Owe 6:4.)

5. Titi emi o fi ri ibikan fun Oluwa, ibùjokòó fun Alagbara Jakọbu." (A.A. 7:46.)

**Imuṣẹ ẹ̀jẹ́ Dafidi.**

6. Kiyesi i, awa gburo rẹ ni Efrata; awa ri i ninu oko jaari. (1 Sam 17:12; 7:1; 1 Kro 13:5.)

7. "Awa o lọ sinu àgọ́ rẹ̀: awa o maa sìn nibi apoti-itisẹ̀ rẹ̀." (Psm 5:7; 99:5.)

8. Oluwa, dide si ibi isinmi rẹ; iwọ, ati apoti agbara rẹ. (Num 10:35; 2 Kro 6:41; Psm 78:61.)

9. Ki a fi ododo wọ awọn alufa rẹ: ki awọn eniyan mímọ́ rẹ maa hó fun ayọ̀. (ẹsẹ 16; Job 29:14; Isa 61:10.)

10. Nitori ti Dafidi iranṣẹ rẹ, máṣe yi ojú ẹni-àmìòróró rẹ padà.

**Ileri Oluwa si Dafidi ati Sioni.**

11. Oluwa ti bura nitootọ fun Dafidi; oun ki yoo yipada ninu rẹ̀, Nínú irú-ọmọ rẹ ni emi o gbé kalẹ si orí ìtẹ́ rẹ. (Psm 89:3,4; 2 Sam 7:12; 2 Kro 6:16.)

12. Bi awọn ọmọ rẹ yoo ba pa majẹmu mi mọ́ ati ẹ̀rí mi ti emi o kọ́ wọn, awọn ọmọ wọn pẹlu yoo jókòó lori ìtẹ́ rẹ laelae." (Luk 1:32; A.A. 2:30.)

13. Nitori ti Oluwa ti yan Sioni; ó ti fẹ ẹ fun ibùjokòó rẹ̀. (Psm 48:1,2; 68:16.)

14. "Èyí ni ibi isinmi mi laelae: nihin lemi o maa gbé; nitori ti mo fẹ ẹ. (ẹsẹ 8.)

15. Emi o bukun ounjẹ rẹ̀ pupọpupọ: emi o fi ounjẹ tẹ awọn talaka rẹ̀ lọ́rùn. (Psm 147:14; 107:9.)

16. Emi o si fi igbala wọ awọn alufa rẹ̀: awọn eniyan mimọ rẹ̀ yoo maa hó fun ayọ̀. (ẹsẹ 9.)

17. Nibẹ ni emi o gbe mu iwọ Dafidi yọ, emi ti ṣe ìlànà fitila kan fun ẹni-àmìòróró mi. (Esk 29:21; Luk 1:69; 1 A.Ọba 11:36; 15:4; 2 Kro 21:7.)

18. Awọn ọ̀tá rẹ̀ lemi o fi ìtìjú wọ̀: ṣugbọn lara oun tikararẹ ni adé rẹ̀ yoo maa gbilẹ̀. (Psm 35:26; 109:29.)

## ORIN 133.

**Ìdàpọ̀ ti awọn ará.**

KIYESI I, o ti dara o si ti dun tó fun awọn ará lati maa jumọ gbe ni ìrẹ́pọ̀. (Gen 13:8; Heb 13:1.)

2. O dabi òróró ikunra iyebiye ni orí, ti o ṣàn dé irungbọn, ani irungbọn Aarọni: ti o si ṣan si etí aṣọ rẹ. (Eks 30:25, 39:24.)

3. Bi iri Hermoni ti o ṣan sórí òkè Sioni: nitori nibẹ ni Oluwa gbé pàṣẹ ìbùkùn, àní ìyè laelae. (Deut 4:48; Lef 25:21; Deut 28:8; Psm 42:8.)

## ORIN 134.

**Ìpè si ìṣó-òru.**

EKIYẸSI I, ẹ fi ibukun fun Oluwa, gbogbo ẹyin iranṣẹ Oluwa, ti nduro ni ilé Oluwa ni òru. (Psm 103:21; 135:1,2; 1 Kro 9:33.)

2. Ẹ gbé ọwọ́ yin sókè si ibi-mimọ, ki ẹ si fi ibukun fun Oluwa. (Psm 28:2; 1 Tim 2:8.)

3. Oluwa ti o da ọrun ati ayé, ki o busi fun ọ lati Sioni wá. (Psm 124:8; 128:5.)

## ORIN 135.

**Ìpè lati yin Oluwa.**

EYIN Oluwa, "Ẹ yin orukọ Oluwa; ẹyin in, ẹ̀yin iranṣẹ Oluwa. (Psm 113:1; 134:1.)

2. Ẹ̀yin ti nduro ni ile Oluwa, ninu àgbàlá ile Ọlọrun wa. (Luk 2:37; Psm 92:13.)

3. Ẹ yin Oluwa: nitori ti Oluwa ṣeun; ẹ kọrin ìyìn si orukọ rẹ̀; ni orin ti o dùn. (Psm 119:68; 147:1.)

4. Nitori ti Oluwa ti yan Jakọbu fun ara rẹ̀; àní Israẹli fun iṣura ààyò rẹ̀. (Deut 7:6,7; 10:15; Eks 19:5; 1 Pet 2:9.)

**Títobi Oluwa.**

5. Nitori ti emi mọ pe Oluwa tobi, ati pé Oluwa ju gbogbo òrìṣà lọ. (Psm 48:1; 97:9.)

6. Ohunkohun ti o wu Oluwa, oun ni o nṣe ni ọrun, ati ni ayé, ni òkun, ati ni ọgbun gbogbo. (Psm 115:3.)

7. O mu ikuukuu awọsanma gòkè lati òpin ilẹ̀ wá: ó dá manamana fún òjò: o nmu afẹ́fẹ́ ti inu ilé iṣura rẹ̀ wá. (Jer 10:13; Job 28:25; Sek 10:1; Job 38:22.)

**Idande ti Oluwa.**

8. Ẹni ti o kọlu awọn akọbi Egipti, ati ti eniyan ati ti ẹranko. (Eks 12:12; Psm 78:51.)

9. Ẹni ti o rán àmì ati iṣẹ́ iyanu si aarin rẹ̀, iwọ Egipti, si ara Farao, ati si ara awọn iranṣẹ rẹ gbogbo. (Psm 78:43; 136:15.)

10. Ẹni ti o kọlu awọn orilẹ-èdè púpọ̀, ti o si pa awọn alagbara ọba. (Num 21:24; Psm 136:17.)

11. Sihoni, ọba awọn ara Amori, ati Ogu, ọba Basani, ati gbogbo ijọba Kenaani. (Num 21:21–26,33–35; Jos 12:7.)

12. O si fi ilẹ̀ wọn funni ni ìní, ìní fun Israẹli, eniyan rẹ̀. (Psm 78:55.)

**Idande ti Ọlọrun.**

13. Oluwa, orukọ rẹ duro laelae; iranti rẹ, Oluwa, lati iran-diran. (Eks 3:15; Psm 102:12.)

14. Nitori ti Oluwa yoo ṣe idajọ awọn eniyan rẹ̀, yoo si ṣe ìyọ́nú si awọn ọmọ-ọdọ rẹ̀. (Deut 32:36; Psm 106:45.)

**Ìwà ibọriṣa orilẹ-èdè.**

15. Fadaka ati wura ni ère awọn Keferi, iṣẹ ọwọ́ eniyan. (Psm 115:4–8.)

16. Wọn ni ẹnu, ṣugbọn wọn ko sọ̀rọ̀; wọn ni ojú, ṣugbọn wọn ko fi riran.

17. Wọn ni etí, ṣugbọn wọn ko fi gbọran; bẹẹ ni ko si eemi kan lẹnu wọn.

18. Awọn ti o ṣe wọn dabi wọn: bẹẹ si ni olukuluku ẹni ti o gbẹkẹle wọn.

**Yin Oluwa, Israẹli.**

19. Ẹ̀yin ara-ile Israẹli, ẹ fi ibukun fun Oluwa, ẹ̀yin ara-ile Aarọni, ẹ fi ibukun fun Oluwa. (Psm 115:9.)

20. Ẹ̀yin ara-ile Lefi, ẹ fi ibukun fun Oluwa; ẹ̀yin ti o bẹ̀rù Oluwa, ẹ fi ibukun fun Oluwa. (Psm 118:4.)

21. Olubukun ni Oluwa, lati Sioni wá, ẹyin ti ngbe Jerusalẹmu. Ẹ fi ìyìn fun Oluwa. (Psm 134:3; 132:14.)

## ORIN 136.

**Ẹ fi ọpẹ́ fun Oluwa.**

EFI ọpẹ́ fun Oluwa: nitori ti o seun; nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae. (Psm 106:1; 107:1; 11:1; 1 Kro 16:34; 2 Kro 20:21.)

2. Ẹ fi ọpẹ́ fun Ọlọrun awọn ọlọrun: nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae. (Deut 10:17.)

3. Ẹ fi ọpẹ́ fun Oluwa awọn oluwa: nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae.

**Ọpẹ́ fun Ọlọrun Ẹlẹda.**

4. Fun oun nikan ti nṣe iṣẹ́ iyanu nla: nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae. (Psm 72:18.)

5. Fun ẹni ti o fi ọgbọ́n da ọrun: nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae. (Gen 1:1; Owe 3:19; Jer 51:15.)

6. Fun ẹni ti o tẹ ilẹ lori omi: nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae. (Gen 1:9; Psm 24:2; Jer 10:12.)

7. Fun ẹni ti o da awọn imọlẹ nla: nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae. (Gen 1:14 16.)

8. Òòrùn lati jọba ọ̀sán: nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae. (Gen 1:15.)

9. Òṣùpá ati ìràwọ̀ lati jọba ọ̀ru: nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae.

**Ọpẹ́ fun Ọlọrun Olugbala Israẹli.**

10. Fun ẹni ti o kọlu Egiptí lara awọn akọbi wọn: nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae. (Eks 12:29; Psm 135:8.)

11. O si mu Israẹli jade kuro laarin wọn: nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae. (Eks 12:51.)

12. Pẹlu ọwọ́ agbara, ati apá nínà: nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae. (Eks 6:6; Psm 44:3; Deut 4:34.)

13. Fun ẹni ti o pin Òkun pupa níyà: nitori ti aanu rẹ̀ dúró laelae. (Eks 14:21; Psm 78:13.)

14. O si mu Israẹli kọja lọ laarin rẹ̀: nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae. (Eks 14:22.)

15. Ṣugbọ̀n o bi Farao ati ogun rẹ̀ ṣubú ninu Òkun pupa: nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae. (Eks 14:27; Psm 135:9.)

16. Fun ẹni ti o sin awọn eniyan rẹ̀ la aginju já: nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae. (Eks 13:18; 15:22; Deut 8:15.)

17. Fun ẹni ti o kọlu ọba nla: nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae. (Psm 135: 10–12.)

18. O si pa awọn ọba olokiki: nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae.

19. Sihoni, ọba awọn ará Amori: nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae.

20. Ati Ogu, ọba Baṣani, nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae.

21. O si fi ilẹ wọn funni ni ìní, nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae. (Jos 12:1.)

22. Ìní fun Israẹli, iranṣẹ rẹ̀; nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae.

**Ọpẹ́ fun Ọlọrun fun ifẹ rẹ ti o durosinsin.**

23. Ẹni ti o ranti wa ni ìwà ìrẹ̀lẹ̀ wa; nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae. (Psm 113:7.)

24. O si dá wa ni ìdè lọ́wọ́ awọn ọ̀tá wa; nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae. (Psm 107:2.)

25. Ẹni ti o nfi ounjẹ fun ẹ̀dá gbogbo: nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae. (Psm 104:27; 145:15.)

26. Ẹ fi ọpẹ́ fun Ọlọrun ọ̀run; nitori ti aanu rẹ̀ duro laelae.

## ORIN 137.

**Ìṣòro Israeli.**

L'ÉBÀÁ odò Babiloni, nibẹ ni awa gbe jókòó, awa si sọkún nigba ti awa ranti Sioni. (Esk 1:1,3; Neh 1:4.)

2. Awa fi dùùrù wa kọ́ si orí igi willo ti o wa laarin rẹ.

3. Nitori pé nibẹ ni awọn ti o ko wa ni ìgbèkùn bèèrè orin lọwọ wa; ati awọn ti o ni wa lara bèèrè idaraya wi pe; "Ẹ kọ orin Sioni kan fun wa." (Psm 80:6.)

**Iranti Sioni.**

4. Awa o ti ṣe kọ orin Oluwa ni ilẹ̀ àjèjì?

5. Jerusalẹmu, bi emi ba gbagbe rẹ, jẹ ki ọwọ́ ọ̀tún mi o gbagbe ìlò rẹ̀.

6. Bi emi ko ba ranti rẹ, jẹ ki ahọn mi o lẹ mọ èrìgì mi; bi emi ko ba fi Jerusalẹmu ṣaaju olori ayọ̀ mi gbogbo. (Esk 3:26.)

**Ìpè si Ọlọrun lati gbẹ̀san.**

7. Oluwa, ranti ọjọ́ Jerusalẹmu lara awọn ọmọ Edomu, awọn ẹni ti nwi pe, "Wó o palẹ, wó o palẹ, de ipilẹ rẹ̀." (Jer 49:7; E.Jer. 4:22; Esk 25:12; Obad 10.)

8. Ìwọ, ọmọbinrin Babiloni, ẹni ti a o parun; ibukun ni fun ẹni ti o san an fun ọ bi iwọ ti hù si wa. (Isa 13:1–6; Jer 25:12; 50:15; Ifh 18:6.)

9. Ibukun ni ẹni ti o mu ọmọ wẹwẹ rẹ ti o si fi wọn ṣán okuta. (2 A.Ọba 8:12; Isa 13:16.)

## ORIN 138.

**Mímọ-rírì otitọ Ọlọrun.**

EMI o maa yìn ọ tinu-tinu mi gbogbo; niwaju awọn òrìṣà ni emi o maa kọrin ìyìn si ọ. (Psm 111:1; 95:3; 96:4.)

2. Emi o maa gbadura sìhà tempili mímọ́ rẹ, emi o si maa yìn orukọ rẹ nitori iṣeun-ìfẹ́ rẹ ati otitọ rẹ; nitori ìwọ gbé ọ̀rọ̀ rẹ ga ju gbogbo orukọ rẹ lọ. (Psm 28:2; 1 A.Ọba 8:29,30.)

3. Ni ọjọ́ ti mo pè, Iwọ da mi lóhùn, iwọ si fi ipá mu mi lara le ni ọkàn mi. (Psm 118:5; 28:7; 46:1.)

**Gbogbo awọn ọba yoo yìn Ọlọrun.**

4. Gbogbo awọn ọba ayé yoo yìn ọ, Oluwa, nigba ti wọn ba gbọ́ ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ. (Psm 102:15.)

5. Nitootọ, wọn o maa kọrin ni ipa-ọ̀nà Oluwa, nitori pé nla ni ogo Oluwa.

6. Bi Oluwa tilẹ ga, sibẹ o juba awọn onirẹlẹ; ṣugbọn agberaga ni o mọ̀ ni òkèrè réré. (Psm 113:5,6; Isa 57:15; Owe 3:34; Jms 4:6.)

**Dafidi ni igbẹkẹle ninu otitọ Ọlọrun.**

7. Bi emi tilẹ nrìn ni ipọnju, iwọ ni yoo sọ mi di ààyè: iwọ o nà ọwọ́ rẹ si ibinu awọn ọ̀tá mi, ọwọ́ ọ̀tún rẹ yoo si gba mi. (Psm 23:3,4; 71:20; Jer 51:25; Psm 20:6.)

8. Oluwa yoo ṣe ohun ti nṣe temi ni àṣepé: Oluwa, aanu rẹ duro laelae: máṣe kọ iṣẹ́ ọwọ́ ara rẹ silẹ̀. (Psm 57:2; Filp 1:6; Psm 136:1; 27:9; Job 10:3,8; 14:15.)

## ORIN 139.

**Ọlọrun ologbon julọ.**

OLUWA, iwọ ti wadi mi, iwọ si ti mọ̀ mi. (Psm 17:3; Jer 12:3.)

2. Iwọ mọ̀ ijokòó mi ati ìdìde mi, iwọ mọ̀ ìrò mi ni ọ̀nà jinjina réré. (2 A.Ọba 19:27; Matt 9:4; Jhn 2:24.)

3. Iwọ yi ipá ọ̀nà mi ká ati idùbúlẹ̀ mi, ọ̀nà mi si di mímọ̀ fun ọ. (Job 31:4.)

4. Nitori ti ko si ọ̀rọ̀ kan ni ahọn mi, kiyesi i, Oluwa, iwọ mọ ọn patapata. (Heb 4:13.)

5. Iwọ sé mi mọ́ lẹhin ati niwaju, iwọ si fi ọwọ́ rẹ le mi. (Psm 34:7; Job 9:33.)

6. Irú ìmọ̀ yìí ṣe ohun ìyanu fun mi jù; o ga, emi kò le mọ̀ ọn. (Rom 11:33; Job 42:3.)

**Ọlọrun wà ni ibi gbogbo.**

7. Nibo ni emi o gbe lọ kuro lọ́wọ́ ẹ̀mí rẹ? Nibo ni emi o salọ niwaju rẹ? (Jer 23:24; Jona 1:3.)

8. Bi emi ba gòkè lọ si ọ̀run, iwọ wà nibẹ̀: bi emi ba sì tẹ́ ẹní mi ni isà-òkú, kiyesi i, iwọ wà nibẹ̀ pẹ̀lú. (Amos 9:2–4; Job 26:6; 17:13 Owe 15:11.)

9. Emi iba mu ìyẹ́-apá owurọ, ki emi si lọ jókòó niha òpin òkun.

10. Ani nibẹ̀ naa ni ọwọ́ rẹ yoo fà mi, ọwọ́ ọ̀tún rẹ yoo si di mi mú. (Psm 23:2,3.)

11. Bi mo ba wi pe, "Njẹ ki okunkun o bo mi mọ́lẹ̀; ki imọlẹ o di òru yi mi ká." (Job 22:13.)

12. Nitootọ òkùnkùn kii ṣú lọdọ rẹ; ṣugbọn òru tan imọlẹ bi ọ̀sán: ati okunkun ati ọ̀sán, mejeji bakannáà ni fun ọ. (Job 34:22; Dan 2:22; Heb 4:13.)

**Ọlọrun ẹlẹda.**

13. Nitori iwọ ni o da ọkàn mi: iwọ ni o bò mi mọlẹ ni inu ìyá mi. (Psm 119:73; Job 10:11.)

14. Emi o yin ọ; nitori tẹru-tẹru ati tiyanu-tiyanu ni a da mi: iyanu ni iṣẹ rẹ; èyí ni ọkàn mi si mọ dájudájú. (Psm 40:5.)

15. Ẹdá ara mi kò pamọ kúrò lọdọ rẹ, nigba ti a da mi ni ikọkọ, ti a si nṣiṣẹ mi ni aràbarà niha isalẹ ilẹ ayé. (Job 10:8–10; Psm 63:9.)

16. Oju rẹ ri ọlẹ mi nigba ti a kòi tii ṣe mi pé; ati ninu iwe rẹ ni a ti kọ ìkọọkan wọn sí, ni ti ọjọ ti a dá wọn, nigba ti wọn kò tilẹ i tii sí.

17. Ọlọrun, ìrò inu rẹ ti ṣe iye-bíye tó fun mi, iye wọn ti pọ tó! (Psm 40:5.)

18. Emi iba kà wọn, wọn ju iyanrin lọ ni iye; nigba tí mo ba jí, emi wà lọdọ rẹ síbẹ.

**Adura ikẹhin lori ọtá.**

19. Ọlọrun iba jẹ pa eniyan buburu nitootọ: nitori naa kuro lọdọ 'mi ẹyin ọkunrin ẹjẹ. (Isa 11:4; Psm 119: 115.)

20. Ẹni ti nfi inú buburu sọrọ si ọ, awọn ọtá rẹ npè orukọ rẹ lásán! (Jud 15.)

21. Oluwa, njẹ emi kò korira awọn ti o korira rẹ? Njẹ inu mi kò ha si bajẹ si awọn ti o dide si ọ? (Psm 119:158.)

22. Emi korira wọn ni àkótán: emi ka wọn si ọtá mi.

23. Ọlọrun, wadi mi, ki o si mọ àyà mi: dan mi wò, ki o si mọ ìrò-inu mi. (Job 31:6; Psm 26:2; Jer 11:20.)

24. Ki o si wò bi ipa-ọnà buburu kan ba wà ninu mi, ki o si fi ẹsẹ mi le ọnà ainipẹkun. (Owe 15:9; Psm 5:8; 143:10.)

## ORIN 140.

**Ẹbẹ fún ìdande kuro lọwọ ẹni-ibi.**

OLUWA gba mi lọwọ awọn ọkunrin buburu, yọ mi lọwọ awọn ọkunrin ìkà. (Psm 17:13; 18:48.)

2. Ẹni ti nro iwà-buburu ni inú wọn; nigbagbogbo ni wọn nrú ìjà sókè si mi. (Psm 36:4; 56:6.)

3. Wọn ti pọn ahọn wọn bi ejò; oró paramọlẹ nbẹ labẹ ètè wọn. (Psm 57:4; 58:4; Jak 3:8.)

4. Oluwa, pa mi mọ kúrò lọwọ eniyan buburu; yọ mi kúrò lọwọ ọkunrin ìkà; ẹni ti o ti pinnu rẹ lati bì ìrìn mi ṣubu. (Psm 71:4.)

5. Awọn agberaga ti dẹkun silẹ fun mi, ati pẹlu okùn ni wọn ti na àwọn; lẹba ọnà ni wọn ti dẹkùn silẹ fun mi. (Psm 35:7; 31:4; 141:9.)

**Ìpè si Ọlọrun lati gbọ.**

6. Emi wi fun Oluwa pé, iwọ ni Ọlọrun mi: Oluwa, gbọ ohùn ẹbẹ mi. (Psm 16:2; 143:1; 116:1.)

7. Ọlọrun Oluwa, agbara ìgbàlà mi, iwọ ni o bo orí mi mọlẹ lọjọ ìjà. (Psm 28:8; 144:10.)

8. Oluwa, máṣe fi ìfẹ́ eniyan buburu fun un: máṣe ran ọgbọn buburu rẹ lọwọ: ki wọn o ma baa gbe ara wọn ga. (Psm 112:10; 10:2.)

**Ìpè si Oluwa lati ṣe idajọ.**

9. Bi o ṣe ti orí awọn ti o yi mi ka kiri ni, jẹ ki ìkà ètè ara wọn bo wọn mọlẹ. (Psm 7:16.)

10. A o da ẹyin iná si wọn lara: Oun o wọ wọn lọ sinu iná, sinu ọgbun omi jìnjìn, ki wọn ó má le dide mọ. (Psm 11:6; 21:9; 36:12.)

11. Máṣe jẹ ki alahọn buburu fi ẹsẹ múlẹ ni ayé: ibi ni yoo maa dọdẹ ọkunrin ìkà lati bii ṣubú. (Psm 34:21.)

**Ọrọ ìgbẹkẹle ninu Ọlọrun.**

12. Emi mọ pe, Oluwa yoo mu ọràn olupọnju duro, yoo si ṣe ètò fun talaka. (Psm 9:4; 35:10.)

13. Nitootọ awọn olododo yoo maa fi ọpẹ fun orukọ rẹ: awọn ẹni didúrọ ṣinṣin yoo maa gbé iwaju rẹ. (Psm 97:12; 11:7.)

ORIN 141.

**Ìwà eniyan rere ninu isoro.**

OLUWA, emi kigbe pè ọ: yara si ọdọ mi; fi etí si ohun mi, nigba ti mo ba nke pè ó. (Psm 22:19; 70:5; 143:1.)

2. Jẹ ki adura mi o wa si iwaju rẹ bi ẹbọ turari; ati ìgbé ọwọ mi soke bi ẹbọ aṣálẹ. (Ifh 5:8; 8:3; Psm 134:2; Eks 29:39.)

**Adura iduro-ṣinṣin.**

3. Oluwa, fi ẹṣọ siwaju ẹnu mi; pa ilẹkùn ètè mi mọ.

4. Máṣe fa àyà mi si ohun ibi kan, lati maa ba awọn ti nṣiṣẹ ẹṣẹ ṣiṣẹ buburu; má si jẹ ki emi o jẹ ninu ohun didun wọn. (Psm 119:36; Owe 23:6.)

**Òpin eniyan buburu.**

5. Jẹ ki olododo o lu mi; iṣeun ni yoo jásí: jẹ kí ó si ba mi wí; òróró daradara ni yoo jasi, Sugbọn ma jẹ kí òróró eniyan buburu kan ori mi, nitori pe ni gba gbogbo ni adura mi yoo doju kọ wọn. (Owe 9:8; Psm 23:5; 35:14.)

6. Nigba ti a ba bi awọn onidájọ wọn ṣubú ni ibi okuta, wọn ó gbọ ọrọ mi, nitori ti o dùn.

7. Egungun wọn yoo tàn kálẹ ni ẹnu isà-òkú, bi ẹni ti o la aporó sórí ilẹ. (Psm 53:5.)

**Ojú mi nwo ọdọ Ọlọrun.**

8. Ṣugbọn ojú mi nbẹ lara rẹ; Ọlọrun Oluwa, lọdọ rẹ ni igbẹkẹle mi wa; máṣe tu ọkàn mi dà sílẹ. (Psm 25:15; 2:12; 27:9.)

9. Pa mi mọ kuro ninu okùn ti wọn dẹ sílẹ fún mi, ati ikẹkun awọn oniṣẹ ẹṣẹ. (O.D. 38:12; 140:5.)

10. Jẹ ki awọn eniyan buburu ó bọ sinu àwọn ara wọn, nigba ti emi ba kọjá lọ. (Psm 35:8.)

ORIN 142.

**Ẹbẹ ẹni-ìgbèkùn.**

OLUWA ni mo fi ohùn mi kigbe pè; ohùn mi ni mo fi nbẹbẹ mi si Oluwa. (Psm 77:1; 30:8.)

2. Emi tu àròyé mi silẹ niwaju rẹ; emi fi iṣẹ mi hàn niwaju rẹ. (Isa 26:16.)

**Ìṣòro ẹni-ìgbèkùn.**

3. Nigba ti ọkàn mi rẹwẹsì ninu mi, nigba naa ni iwọ mọ ipa-ọnà mi, Ni ọnà ti emi nrin ni wọn dẹkùn silẹ fun mi níkọkọ. (Psm 143:4; 140:5.)

4. Emi wo ọwọ ọtún, mo si ri pe, kò si ẹnikan ti o mọ mi: aabo kò sí fun mi, ko si ẹni ti o naani ọkàn mi. (Psm 31:11; Job 11:20; Jer 30;17.)

**Adura fun idande.**

5. Oluwa, iwọ ni mo kigbe pè: emi wi pe, iwọ ni ààbò mi ati ìpín mi ni ilẹ alaaye. (Psm 46:1; 16:5; 27:13.)

6. Fiyesi igbe mi: nitori ti a rẹ mi silẹ gidigidi: gba mi lọwọ awọn oninunibini mi, nitori wọn lágbára jù mí lọ.

7. Mu ọkàn mi jade kuro ninu túbú, ki emi le maa yin orukọ rẹ; awọn olododo yoo yi mi ká kiri; nitori iwọ o fi ọpọlọpọ wọn ba mi ṣe. (Psm 146:7; 13:6.)

ORIN 143.

**Ẹdùn-ọkàn Ọlọrun.**

OLUWA, gbọ adura mi, fi etí si ẹbẹ mi; ninu otitọ rẹ da mi lohun, ati ninu ododo rẹ! (Psm 140:6; 89:1,2; 71:2.)

2. Ki o ma si ba ọmọ-ọdọ rẹ lọ sinu idajọ; nitori ti ko si ẹni ti o wa laaye ti a o dalare niwaju rẹ. (Job 14:3; 4:17; Psm 130:3; Onws 7:20; Rom 3:20.)

3. Nitori tí ọtá ti ṣe inunibini si ọkàn mi; o ti lù ẹmí mi bolẹ; o ti mu mi jókòó ni òkùnkùn, bi awọn ti o ti kú pé.

4. Nitori naa ni ẹmi mi ṣe rẹwẹsi ninu mi; ọkan mi ninu mi nfòyà. (Psm 142:3; E.Jer. 3:11.)

5. Emi ranti ọjọ àtijọ; emi ṣe àṣàrò iṣẹ rẹ gbogbo, emi nronu iṣẹ ọwọ rẹ. (Psm 77:5; 77:12; 105:2.)

6. Emi na ọwọ mi si ọ; oungbẹ rẹ ngbẹ mi bi ilẹ gbígbẹ. (Psm 88:9; 63:1.)

**Ẹbẹ̀ fun idande.**

7. Oluwa, gbọ́ temi nisinsinyìí; ó rẹ ọkàn mi tán; máṣe pa ojú rẹ mọ́ kúrò lara mi, ki emi ma ba dabi awọn ti o lọ sinu ihò. (Psm 69:17; 27:9; 27:9; 28:1.)

8. Mu mi gbọ iṣeun-ìfẹ́ rẹ ni owurọ; nitori iwọ ni mo gbẹkẹle: mu mi mọ ọ̀nà ti emi ìbá tọ̀; nitori mo gbé ọkàn mi sókè sí ọ. (Psm 90:14; 25:2; 27:11; 25:1.)

9. Oluwa, gbà mi lọ́wọ́ awọn ọ̀tá mi: ọ̀dọ̀ rẹ ni mo sa pamọ́ sí. (Psm 31:15.)

10. Kọ mi lati ṣe ohun ti o wù ọ́: nitori iwọ ni Ọlọrun mi; jẹ ki ẹ̀mí rẹ didara fa mi lọ ni ilẹ ti o tẹ́jú. (Psm 25:4,5; Neh 9:20; Psm 23:3.)

11. Oluwa, sọ mi di ààyè nitori orukọ rẹ: ninu ododo rẹ mu ọkàn mi jade ninu ìṣẹ́. (Psm 119:25; 31:1.)

12. Ati ninu aanu rẹ gé awọn ọ̀tá mi kuro, ki o si run gbogbo awọn ti nni ọkan mi lara; nitori pé iranṣẹ rẹ lemi jẹ. (Psm 54:5; 52:5; 116:16.)

## ORIN 144.

**Ìyìn Ọlọrun Ọga-Ogo.**

OLUBUKUN ni Oluwa apata mi, ẹni ti o kọ́ ọwọ́ mi ni ogun, ati ìka mi ni ìjà. (Psm 18:2,34.)

2. Ọrẹ mi, ati odi-agbara mi; ile-ìṣọ́ giga, ati olugbala mi; asà mi, ati ẹni ti mo gbẹkẹle; ẹni ti o terí awọn eniyan mi ba lábẹ́ mi. (Psm 91:2; 59:9; 84:9; 18:39.)

3. Oluwa, kinni eniyan, ti iwọ fi nkiyesi i! Tabi ọmọ eniyan, ti iwọ fi nrò nipa rẹ̀! (Psm 8:4; Heb 2:6.)

4. Eniyan dabi asán: bi ojiji ti nkọja lọ ni ọjọ́ rẹ̀. (Psm 39:11; 102:11.)

**Adura fun iranlọwọ ati idande.**

5. Oluwa, tẹ̀ ọrùn rẹ ba, ki o si sọkalẹ: Tọ́ awọn òkè nla, wọn o si rú ẹefin. (Psm 18:9; Isa 64:1; Psm 104:32.)

6. Ki manamana jade, ki o si tu wọn ká: ta ọfà rẹ ki o si pa wọn run. (Psm 18:13,14; 7:13.)

7. Ran ọwọ́ rẹ lati òkè wa; yọ mi, ki o si gbà mi kúrò ninu omi nla, ni ọwọ́ awọn ọmọ àjèjì. (Psm 69:1,14; 18:44.)

8. Ẹnu ẹni ti nsọrọ asán, ọwọ ọ̀tún wọn si jẹ ọwọ́ ọ̀tún èké. (Psm 12:2; Isa 44:20.)

9. Ọlọrun, emi o kọ orin titun si ọ: lara ohun ọ̀nà orin olokun mẹwa ni emi o kọrin ìyìn si ọ. (Psm 33:2,3.)

10. Oun ni o nfi ìgbàlà fun awọn ọba: ẹni ti o gba Dafidi iranṣẹ rẹ lọ́wọ́ idà pipanilara. (Psm 18:50; 140:7.)

11. Yọ mi, ki o si gbà mi lọ́wọ́ awọn ọmọ àjèjì, ẹnu ẹni ti nsọrọ asán, ati ọwọ́ ọ̀tún wọn jẹ ọwọ́ ọ̀tún èké. (Psm 12:2; Isa 44:20.)

**Adura fun ibukun.**

12. Ki awọn ọmọkunrin wa, o dabi igi gbígbìn ti o dàgbà ni ìgbà-èwe wọn; ki awọn ọmọbinrin wa o le dabi ọ̀wọ̀n igun-ile, ti a ṣe lọ́nà bi afarawe aafin. (Psm 128:3.)

13. Ki àká wa o le kún, ki o maa funni ni oniruuru iṣura: ki awọn aguntan wa maa bí ẹgbẹẹgbẹrun ati ẹgbẹẹgbẹrun mẹwa ni igboro wa.

14. Ki awọn malu wa o le rẹrù; kí o maásì si ìkọlù, ikolọ jade; ki o maásì si àròyé ni igboro wa.

15. Ibukun ni fun awọn eniyan, ti o nbẹ ni irú ìwà bẹẹ: nitootọ, ìbùkún ni fun awọn eniyan naa, ti ẹni ti Ọlọrun Oluwa nṣe. (Psm 33:12.)

## ORIN 145.

**Titobi Ọlọrun.**

EMI o gbe ọ ga, Ọlọrun mi, ọba mi; emi o si maa fi ibukun fún orukọ rẹ lae ati laelae. (Psm 30:1; 5:2; 34:1.)

2. Ni ojojumọ ni emi o maa fi ibukun fun ọ; emi o si maa yin orukọ rẹ lae ati laelae. (Psm 71:6.)

3. Titobi ni Oluwa, o si ni ìyìn púpọ̀púpọ̀; àwámárídìí si ni titobi rẹ̀. (Psm 96:4; Job 5:9; Rom 11:33.)

4. Iran kan yoo jíyìn iṣẹ rẹ fun ikeji, yoo si maa sọ̀rọ̀ iṣẹ́ agbara rẹ̀. (Isa 38:19.)

5. Emi o sọrọ ìyìn ọla-nla rẹ ti o logo, ati ti iṣẹ́ iyanu rẹ. (ẹsẹ 12; Psm 119:27.)

6. Eniyan o si maa sọ̀rọ̀ agbara iṣẹ́ rẹ ti o ni ẹrù; emi o si maa ròhìn titobi rẹ. (Psm 66:3; Deut 32:3.)

7. Wọn o maa sọ̀rọ̀ iranti oore rẹ púpọ̀púpọ̀, wọn o si maa kọrin ododo rẹ. (Isa 63:7; Psm 51:14.)

**Ogo Ọlọrun.**

8. Oloore-ọfẹ ni Oluwa, o kun fun aanu; o lọra lati binu, o si ni aanu pupọ. (Eks 34:6; Psm 86:5–15.)

9. Oluwa ṣeun fun ẹni gbogbo; ìyọ́nú rẹ̀ si nbẹ lori iṣẹ́ rẹ gbogbo. (Psm 100:5; Neh 1:7.)

10. Oluwa, gbogbo iṣẹ́ rẹ ni yoo maa yìn ọ́; awọn eniyan mimọ rẹ yoo si maa fi ibukun fun ọ. (Psm 19:1; 68:26.)

11. Wọn o maa sọ̀rọ̀ ògo ijọba rẹ, wọn o si maa sọ̀rọ̀ agbara rẹ.

12. Lati mú iṣẹ́ agbara rẹ di mímọ̀ fun awọn ọmọ eniyan, ati ọla-nla ijọba rẹ ti o logo. (Psm 105:1; ẹsẹ 5.)

13. Ijọba rẹ ijọba ayé-rayé ni, ati ijọba iran-diran gbogbo. (Psm 146:10; 2 Pet 1:11.)

**Ododo Oluwa.**

14. Oluwa gbé gbogbo awọn ti o nṣubútọ ró; o si gbe gbogbo awọn ti o tẹ̀ba dide. (Psm 37:24; 146:8.)

15. Ojú gbogbo eniyan nwò ọ; iwọ si fun wọn ni ounjẹ wọn ni àkókò rẹ̀. (Psm 104:27.)

16. Iwọ ṣi ọwọ́ rẹ, iwọ si té ifẹ gbogbo ohun alaaye lọ́rùn. (Psm 124:28.)

17. Olododo ni Oluwa ni ọ̀nà rẹ̀ gbogbo, ati alaanu ni iṣẹ́ rẹ̀ gbogbo.

18. Oluwa wa leti ọdọ gbogbo awọn ti nke pe e, leti ọdọ gbogbo ẹni ti nke pe e ni otitọ. (Deut 4:7; Jhn 4:24.)

19. Yoo mu ìfẹ́ awọn ti nbẹ̀rù rẹ̀ ṣẹ; yoo gbọ́ igbe wọn pẹlu, yoo si gbà wọ́n. (Psm 37:4; Owe 15:29.)

20. Oluwa da gbogbo awọn ti o fẹ ẹ sí: ṣugbọn gbogbo eniyan buburu ni yoo parun. (Psm 31:23; 97:10; 9:5.)

21. Ẹnu mi yoo ma sọ̀rọ̀ ìyìn Oluwa, ki gbogbo eniyan si maa fi ibukun fun orukọ rẹ̀ mímọ́ (Psm 7:8; 65:2; ẹsẹ 1,2.)

## ORI 146.

**Igbẹkẹle eniyan asán ni.**

EFI ìyìn fun Oluwa. Fi ìyìn fun Oluwa iwọ ọkàn mi. (Psm 148:1; 103:1; 104:1.)

2. Nigba ti mo wa láàyè ni emi o maa fi ìyìn fun Oluwa: emi o maa kọrin ìyìn si Ọlọrun mi, nigba ti mo si wà. (Psm 104:33.)

3. Ẹ máṣe gbẹkẹ yin le awọn ọmọ-alade, ani le ọmọ-eniyan, lọwọ ẹni ti ko si iranlọwọ. (Psm 118:8; Isa 2:22.)

4. Ẹ mi rẹ̀ jade lọ, o pada si erùpẹ̀ rẹ̀; ni ọjọ́ naa gan, ìrò inu rẹ̀ run. (Psm 104:29; Onws 12:7; Psm 33:10.)

**Ọgbọ́n wa ninu gbigbẹkẹle Ọlọrun.**

5. Ibukun ni fun ẹni ti o ni Ọlọrun Jakọbu fun iranlọwọ rẹ̀, ireti ẹni ti nbẹ lọdọ Oluwa Ọlọrun rẹ̀. (Psm 144:15; 71:5.)

6. Ẹni ti o da ọ̀run ati ayé, òkun ati ohun ti o wa ninu wọn: ẹni ti o pa otitọ mọ́ títí ayé. (Psm 115:15; A.A. 14:15; Psm 117:2.)

7. Ẹni ti o nṣe idajọ fun ẹni-inilara: ẹni ti o nfi ounjẹ fun ẹni ti ebi npa, Oluwa tú awọn ara túbú sílẹ̀. (Psm 103:6; 107:9; 68:6.)

8. Oluwa ṣi ojú awọn afọ́jú: Oluwa gbe awọn ti a tẹ̀ lórí ba dide; Oluwa fẹ awọn olododo. (Matt 9:30; Jhn 9:7; Psm 145:14; 11:7.)

9. Oluwa pa awọn alejo mọ́; ó tu awọn alainibaba ati opó lara: ṣugbọn ọ̀nà awọn eniyan buburu ni yoo parun. (Eks 22:21; Deut 10:18; Psm 68:5; 147:6.)

10. Oluwa yoo jọba laelae, àní Ọlọrun rẹ, iwọ Sioni, lati iran-diran gbogbo. Ẹ fi ìyìn fun Oluwa. (Eks 15:18; Psm 10:16; Ifh 11:15.)

## ORIN 147.

**Ọlọrun alagbara ati ologo.**

EFI ìyìn fun Oluwa: nitori ohun rere ni lati maa kọ orin ìyìn si Ọlọrun wa: nitori ti o dùn, ìyìn si yẹ. (Psm 135:3; 33:1.)

2. Oluwa ni o kọ́ Jerusalẹmu Oun ni o kó awọn ifọnkalẹ Israẹli jọ. (Psm 102:16; Deut 30:3.)

3. O mu awọn onirora àyà lara dá: o di ọgbẹ́ wọn. (Isa 61:1; 30:26.)

4. O ka iye awọn ìràwọ̀; o si pe gbogbo wọn ni orukọ. (Isa 40:26.)

5. Oluwa wa tobi, ati alagbara nla; òye rẹ̀ kò ni òpin. (Psm 48:1; Isa 40:28.)

6. Oluwa gbe awọn onirẹlẹ sókè: o rẹ awọn eniyan buburu sílẹ̀. (Psm 146:8,9.)

**Ọlọrun orisun ìyè.**

7. Ẹ fi ọpẹ́ kọrin si Oluwa; kọrin ìyìn si Ọlọrun wa lara dùùrù. (Psm 33:2.)

8. Ẹni ti o fi ìkúukùu awọsanma bò ojú ọ̀run, ẹni ti o pèsè òjò fun ilẹ, ti o mu koriko dàgbà lori awọn òkè. (Job 38:26; Psm 104:13.)

9. O fi ounjẹ awọn ẹranko fun un, ati fun awọn ọmọ ẹyẹ-iwo ti nké. (Psm 104:27; Job 38:41.)

10. Ko ṣe inudidun si agbara ẹṣin: tabi ṣe inudidun si ẹsẹ̀ ọkunrin. (Psm 33:16,17; 1 Sam 16:7.)

11. Oluwa nṣe inudidun si awọn ti o bẹru rẹ̀, si awọn ti nṣe ireti aanu rẹ̀. (Psm 102:15.)

**Ẹ yin Ọlọrun Israẹli.**

12. Yin Oluwa, iwọ Jerusalẹmu! Yin Ọlọrun rẹ, iwọ Sioni!

13. Nitori ti o ti mu ọ̀pá-idabu ẹnu-bode rẹ le; o ti busi fun awọn ọmọ rẹ ninu rẹ. (Psm 37:26.)

14. O fi alaafia ṣe agbegbe rẹ, o si fi alikama didara-jù kún ọ. (Isa 60:17; Psm 132:15.)

15. O ran àṣẹ rẹ̀ jade wa si ayé; ọ̀rọ̀ rẹ̀ sure tete. (Job 37:12; Psm 104:4.)

16. O fi òjò dídì funni bi irun-agutan, o si fún ìrì-dídì ka bi eeru. (Job 37:6; 38:29.)

17. O da omi-dídì rẹ bi òkèlè; tani o le duro niwaju òtútù rẹ̀.

18. O ran ọ̀rọ̀ rẹ jade, o si mu wọn yọ́; o mu afẹ́fẹ́ rẹ fẹ, omi si nṣan. (Psm 33:9; 107:25.)

19. O fi ọ̀rọ̀ rẹ̀ hàn fun Jakọbu, àṣẹ rẹ̀ ati idajọ rẹ̀ fun Israẹli. (Deut 33:2; Mal 4:4.)

20. Ko ba orilẹ-èdè kan ṣe bẹẹ ri; bi o si ṣe ti idajọ rẹ ni, wọn kò mọ̀ wọn, Ẹ fi ìyìn fun Oluwa." (Deut 4:32.)

## ORIN 148.

**E yin Ọlọrun, ẹ̀yin ọ̀run.**

EFI ìyìn fun Oluwa, ẹ fi ìyìn fun Oluwa, lati ọ̀run wá; ẹ fi ìyìn fun un ni ibi giga.

2. Ẹ fi ìyìn fun un, gbogbo ẹ̀yin angẹli rẹ̀; ẹ fi ìyìn fun un, gbogbo ẹ̀yin ọmọ-ogun rẹ̀. (Psm 103:20,21.)

3. Ẹ fi ìyìn fun un, òòrùn ati ọṣupa; ẹ fi ìyìn fun un, gbogbo ẹ̀yin ìràwọ̀ imọlẹ!

4. Ẹ fi ìyìn fun un, ẹ̀yin ọ̀run awọn ọ̀run, ati omi ti nbẹ loke ọ̀run. (1 A.Ọba 8:27; Gen 1:7.)

5. Jẹ ki wọn maa yin orukọ Oluwa; nitori ti o paṣẹ, a si da wọn. (Gen 1:1; Psm 33:6,9.)

6. O si fi ìdí wọn múlẹ̀ lae ati laelae; o si ti ṣe ìlànà kan ti ki yoo kọja. (Psm 89:37; Jer 33:25; Job 38:33.)

**Ẹ yin Ọlọrun ẹ̀yin ayé.**

7. Ẹ yin Oluwa lati ayé wá, ẹ̀yin erinmi, ati gbogbo ibú-omi. (Psm 74:13.)

8. Iná ati yìnyín, òjò dídì ati ikuukuu; ìjì mú ọ̀rọ̀ rẹ̀ ṣẹ! (Psm 147:15–18.)

9. Ẹyin òkè nla, ati gbogbo òkè kekere; igi eleso, ati gbogbo igi Kedari. (Isa 44:23; 49:13; 55:12.)

10. Ẹranko, ati gbogbo ẹran-ọ̀sìn; ohun ti nrákò, ati ẹyẹ ti nfò.

11. Awọn ọba ayé, ati eniyan; ọmọ-alade, ati gbogbo onidajọ ayé.

12. Awọn ọdọmọkunrin ati awọn wundia, awọn arugbo eniyan ati awọn ọmọde.

13. Ki wọn maa yin orukọ Oluwa; orukọ rẹ̀ nikan ni o ni ọlá; ogo rẹ̀ bori ayé ati ọ̀run. (Psm 8:1; Isa 12:4; Psm 113:4.)

14. O si gbe ìwo kan sókè fun awọn eniyan rẹ̀, iyin fun gbogbo eniyan mímọ́ rẹ̀; àní awọn ọmọ Israẹli, awọn eniyan ti o sunmọ ọdọ rẹ̀, Ẹ fi ìyìn fun Oluwa. (Psm 75:10; Deut 10:21; Ef 2:17.)

## ORIN 149.

**Orin titun si Ọlọrun Israẹli.**

EFI ìyìn fun Oluwa! Ẹ kọ orin titun si Oluwa, ati ìyìn rẹ̀ ninu ijọ awọn eniyan-mimọ! (Psm 33:3; 35:18.)

2. Jẹ ki Israẹli yọ̀ si ẹni ti o da a; jẹ ki awọn ọmọ Sioni kun fun ayọ̀ si Ọba wọn! (Psm 95:6; 47:6.)

3. Jẹ ki wọn yin orukọ rẹ̀ ninu ìjọ: jẹ ki wọn o fi ìlù ati dùùrù kọrin ìyìn si i. (Psm 150:4; 81:2.)

4. Nitori ti Oluwa ṣe inudidun si awọn eniyan rẹ̀; yóò fi ìgbàlà ṣe awọn onirẹlẹ lẹ́wà. (Psm 35:27; 132:16.)

**Ìpè lati gbẹsan lori orilẹ-èdè.**

5. Jẹ́ ki awọn eniyan mimọ kún fun ayọ̀ ninu ògo; ki wọn maa kọrin kíkan lori ẹni wọn. (Psm 132:16; Job 35:10.)

6. Ki ìyìn Ọlọrun wa lẹnu wọn, ati idà olójú meji ni ọwọ́ wọn. (Psm 66:17; Heb 4:12; Ifh 1:16.)

7. Lati ṣan ẹ̀san lara awọn Keferi, ati ìjìyà lara awọn eniyan.

8. Lati fi ẹ̀wọn de awọn ọba wọn, ati lati fi ṣẹ́kẹ́ṣẹkẹ̀ irin de awọn ọlọla wọn.

9. Lati ṣe idajọ ti a ti kọwe rẹ̀ lori wọn. Ọlá yií ni gbogbo eniyan mimọ rẹ̀ ni. "Ẹ fi ìyìn fun Oluwa." (Esk 28:26; Psm 148:14.)

## ORIN 150.

**Fi ohun gbogbo yin Oluwa.**

EFI iyin fun Oluwa, Ẹ fi ìyìn fun Ọlọrun ninu ibi mimọ rẹ̀; yin in ninu ofurufu ojú-ọ̀run agbara rẹ̀. (Psm 102:19; 19:1.)

2. Yin in nitori iṣẹ́ agbara rẹ̀: yin in gẹgẹ bi titobi nla Rẹ̀. (Psm 145:5,6; Deut 3:24.)

3. Fi ohùn ìpè yin in: fi ohun-èlò orin ati dùùrù yin in. (Psm 149:3.)

4. Fi ìlù ati ijó yin in: fi ohun ọnà orin olokun ati fèrè yin in. (Eks 15:20; Isa 38:20.)

5. Ẹ yin in lara arò olóhùn òkè: ẹ yin in lara arò olohun goro. (1 Kro 13:8; 15:16.)

6. Jẹ ki ohun gbogbo ti o ni eemi yin Oluwa. Ẹ fi ìyìn fun Oluwa! (Psm 145:21.)